# NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA (NOUN)

## YOR: YOR 361: ÌFÁÁRÀ SÍ ERÉ-ONÍṢE NÍ ÈDÈ YORÙBÁ
## (YOR 361: INTRODUCTION TO DRAMA IN YORÙBÁ)

Òjọ̀gbọ́n Philip Adédọ̀tun Ògúndèjì FNAL
B. A. M. A. Ph. D. Ìbàdàn

Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ Ẹ̀dá-èdè àti Èdè Ilẹ̀ Áfíríkà
Yunifásítì Ìbàdàn, Ìbàdàn.

(Department of Linguistics and African Languages
University of ìbádàn, Ìbàdàn.)

KÓÒDÙ KỌ́Ọ̀SÌ: YOR 361
ÀKỌLÉ KỌ́Ọ̀SÌ: ÌFÁÁRÀ SÍ ERÉ-ONÍṢE NÍ ÈDÈ YORÙBÁ

ÀPÈJÚWE KỌ́Ọ̀SÌ: Ọwọ́jà kọ́ọ̀sì yìí dé orí gbogbo ohun tí eré-oníṣe jẹ́ ní èdè àti àṣà Yorùbá; àgbéyẹ̀wò eré-onítàn ṣiṣe àti kíkọ níbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, ipa eré-oníṣe àbáláyé, tí òde òní tó ṣàmúlò èròjà tìbílẹ̀, àti àyẹ̀wò àwọn eré-oníṣe àpilẹ̀kọ.

COURSE CODE: YOR 361
COURSE TITLE: INTRODUCTION TO DRAMA

COURSE DESCRIPTION: This course covers the concept of drama in Yoruba; a survey of early attempts at play writing and play acting, the influence of traditional and folk drama, and an appraisal of the written plays.

Òǹkọ̀wé Kọ̀ọ̀sì: Ọ̀jọ̀gbọ́n Philip Adédọ̀tun Ògúndèjì FNAL

Olóòtú Kọ̀ọ̀sì: Ọ̀jọ̀gbọ́n Lérè Adéyẹmí

ÀKÓÓNÚ KỌ́Ọ̀SÌ

## MÓDÙ 1: ÌFÁÀRÀ GBOGBOGBÒÒ


Ìpín 1 Èdè Ìperí.
Ìpín 2 Ìpínsísọ̀rí gbogbogbòò fún eré-oníṣe Yorùbá.
Ìpín 3 Àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bí i tíátà (ìṣeré).
Ìpín 4 Àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bí i lítíréṣọ̀.


## MÓDÙ 2: ERÉ-ONÍṢE ÀBÁLÁYÉ


Ìpín 1 Ǹjẹ́ eré-oníṣe ni òdún ìbílẹ̀?

Ìpín 2 Ìpínsísọ̀rí àti ìṣàmúlò ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá.
Ìpín 3 Eégún aláré: Orúkọ, ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè.
Ìpín 4 Ìṣeré eégún aláré.
Ìpín 5 Oríṣiríṣi eré eégún aláré.


## MÓDÙ 3: ERÉ-ONÍṢE ÒDE-ÒNÍ


Ìpín 1 Eré onílànà Ogunde: Orúkọ, ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè.
Ìpín 2 Àbùdá ìṣeré onílànà Ogunde ajẹmọ́ṣeré àti ajẹmọ́ lítíréṣọ̀.
Ìpín 3 Ìpínsísọ̀rí eré-oníṣe onílànà Ogunde.
Ìpín 4 Ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá.

Ìpín 5: Ìpínsísọ̀rí eré-onítàn àpilẹ̀kọ Yorùbá.
Ìpín 6: Ìjẹyọ eré-oníṣe àbáláyé nínú tòde òní.




1. 0 ÌFÁÁRÀ SÍ KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ

Eré-oníṣe (tàbí dírámà) ni kọ̀ọ̀sì àìgbọdọ̀-má-ṣe yìí dá lé. Yúníìtì mẹ́ta (3 Units) sì ni. Àìgbọdọ̀-má-ṣe tí kọ̀ọ̀sì náà jẹ́ túmọ̀ sí wí pé kí ó tó lè ṣe àṣeyege ninú ìkẹ́kọ̀ọ́ gboyè rẹ ó pọn dandan kí o ṣe kọ̀ọ̀sì yìí, kí o sì yege nínú rẹ̀. Ìdí nìyí tí mo fi ń gbà ọ́ ní ìmọ̀ràn pé kí o múra sí i gidigidi. Èmi gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ rẹ ti sa gbogbo ipá mi láti mú kí àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà ó tètè yé ọ. Lára ète tí mo dá nípa èyí ni nípa lílo ọ̀pọ̀lọpọ̀ búlẹ́ẹ̀tì, kí o lè máa rí àwọn kókókókó kí o sì máa fi ọkàn bá a lọ bí wọ́n ṣe tẹ̀lé ara wọn ní ṣísẹ̀ntẹ̀lé. Ní àfikún mo gbìyànjú láti ṣe àpẹẹrẹ níbi tí ó yẹ.

Módù mẹ́ta ni a pín gbogbo iṣẹ́ náà sí. Ìpín mẹ́rin ni Módù kìn-ín-ní ní, Ìkejì ní ìpín márùn-ún, ìkẹta sì ní mẹ́fà. Apapọ̀ gbogbo ìpín inú Kọ̀ọ̀sì yìí jẹ́ mẹ́ẹ̀dógún. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan ni ìpín kọ̀ọ̀kan jẹ́. Èyí túmọ̀ sí wí pé ìdánilẹ́kọ̀ọ́ mẹ́ẹ̀dógún ni gbogbo àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀sì yìí. Abala mẹ́ta ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan ní; Ìbẹ̀rẹ̀, Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìparí. Abala ìbẹ̀rẹ̀ ni ìfáàrà (1. 0), èròǹgbà (2. 0) pẹ̀lú ìbéèrè ìṣájú (3. 0) wà, kí ó tó kan ìdánilẹ́kọ̀ọ́ gan-an-gan (4.0). A gbìyànjú láti pín ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà sí ẹ̀ka kéékèké láti jẹ́ kí o lè máa lọ láti ìgbésẹ̀ kan dé ìkejì àti ní ẹsẹ ẹsẹ. Abala ìparí ni Ìsọníṣókí (5. 0), Iṣẹ́ àmúṣe (6. 0) àti Ìwé ìtọ́kasí (7. 0) wà. Ìlànà ètò yìí wà láti mú ìkẹ́kọ̀ọ́ dẹrùn fún ọ.

Bí o bá ní àfojúsùn láti ṣe àṣeyọrí rere, tí o sì fẹ́ gbádùn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú kọ̀ọ̀sì yìí dáradára, ó di dandan kí o ṣe àwárí àwọn àpẹẹrẹ tara tìrẹ, yàtọ̀ sí àwọn èyí tí èmi, gẹ́gẹ́ bí olùkọ́ rẹ ṣe fún ọ nínú àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inu kọ̀ọ̀sì yìí. Nípa kíka àwọn ìwé ìtọ́kasí tí a kó jọ sí ìparí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan àti àwọn ìwé mìíràn, bẹ́ẹ̀ tí ìwọ náà tún ṣe àwárí, ni ó ṣe lè ṣe eléyìí.

Àpilẹ̀ṣe ni àwọn eré-oníṣe àbáláyé tí a gbé yẹ̀wò nínú kọ̀ọ̀sì yìí, wọn kì í ṣe àpilẹ̀kọ, ìyẹn ni pé kò sí àkọsílẹ̀ eré wọn láti ilẹ̀ wá. Níwọ̀n ìgbà tí wọ́n ṣì ń ṣe nínú wọn ní àwùjọ títí di òní, yóò dára bí o bá tún ṣe ìwádìí lọ́dọ̀ àwọn tí wọ́n nímọ̀ nípa àṣà eré àbáláyé náà (àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá àti ìdán àwọn eléégún aláré). Kò sí àkọsílẹ̀ àtilẹ̀wá fún àwọn eré onílànà Ogunde náà. Ṣùgbọ́n o lè rí àdàkọ díẹ̀ nínú wọn, o sì lè rí àwọn èyí tí wọ́n ṣe sínú ìwé eré onífọ́tò *Atọ́ka* àti àwọn tí wọ́n ṣe sórí fọ́n-ọ̀n-rán téèpù oníkáṣẹ́ẹ̀tì, awo Síí Diì, yálà onífídíò móhùn-máwòrán tàbí ti amóhùn nìikan. O sì tún lè wo ìtàkùn àgbáyé àti pàápàá 'You Tube' àti 'Face Book' fún àpẹẹrẹ oríṣiríṣi eré onífídíò òde òní. Gbogbo èyí yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ gidigidi, yóò sì tún mú kí ìmọ̀ rẹ kún sí i. Àbèèrè ọnà ni kì í ṣìnà o. Ìmọ̀ràn míràn tí mo tún ní fún ọ ni pé kí o rí i dájú pé o kó ara rẹ níjàánu láti máa ka àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà déédéé kí o sì máa ṣe gbogbo àwọn iṣẹ́ àmúṣe tí a yàn fún ọ ní àsìkò. Má fi òní dá ọla, kí ó má báà yọ sílẹ̀ lẹ́yìnọ̀rẹyìn; kí ó má sì wá já sí àbámọ̀ fun ọ. Ààbọ̀ ọ̀rọ̀ là á sọ fún ọmọlúwàbí, bí ó bá dé inú rẹ̀ ní í di odindi o. Àṣeyè lalákàn ń ṣepo o; àṣeyè ni o ó ṣe kọ̀ọ̀sì yí àti àwọn yòókù náà o. Múra o!

Ire!

Olùdánilẹ́kọ̀ọ́ rẹ



2. 0 ÀFOJÚSÙN KỌ̀Ọ̀SÌ YÍ

Lẹ́yìn tí o  bá ti ka gbogbo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ́ọ̀sì yí ní àkàyé tán, o óò lè jíròrò nípa:

- Ọdún ìbílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí eré-oníṣe àbáláyé.
- Eré àti ìṣeré àwọn eléégún aláré.
- Eré àti ìṣeré àwọn eléré onílànà Ogunde.
- Eré ònítàn àpilẹ̀kọ.

Àwọn ohun tí a tẹnu mọ́ láti rí i pé àmójúsùn wa yìí kẹ́sẹ járí ni àwọn orúkọ tí a fi ṣe ìdámọ̀ àwọn ìṣeré náà, ìtàn ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè wọn, àpèjúwe ìṣeré àti ìpínsísọ̀rí àwọn eré náà.

v

3. 0 OJÚṢE AKẸ́KỌ̀Ọ́

Àwọn ojúṣe rẹ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ kọ́ọ̀sì yìí nìwọ̀nyí:

1. Dáhùn àwọn ìbéèrè ìṣaájú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan kí ó tó bẹ̀rẹ̀ sí í ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà. Èyí wà láti mú ọ rántí ìmọ̀ àtẹ̀yìn-wá. Ó sì tún wà láti ràn ọ́ lọ́wọ́ kí ó lè pèsè ọkàn rẹ sílẹ̀ fún àwọn nǹkan tuntun tí o ó ṣẹ̀ṣẹ̀ kọ́ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí o fẹ́ kà náà.
2. Ka àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú ìwé kọ́ọ̀sì yìí ní àkàyé.
3. Wá àwọn àpẹẹrẹ mìíràn tí ó bá ohun tí o kà mu dáadáa. Èyí ni yóò jẹ́ ìdánilójú pé àwọn ohun tí o kà yé ọ dáradára. Nípa kíka àwọn ìwé mìíràn àti ṣíṣe ìwádìí síwájú sí i láwùjọ ni ó ṣe lè ṣe èyí. O óò rí àpẹẹrẹ àkọlé àwọn ìwé tí ó lè kà sí i ní àbẹ́ 'Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí' (7.0)
4. Dáhùn àwọn ìbéèrè ìkẹyìn tí ó wà lábẹ́ àkọlé Ìṣẹ́ àmúṣe (6. 0). Èyí ni yóò dúró bí ìranni létí ohun tí o ṣẹ̀ṣẹ̀ kà tán, tí yóò sì tún jẹ́ kí o lè mọ̀ bí àwọn ohun tí o kà náà ti yé ọ sí.
5. Bí ó bá nílò ìrànlọ́wọ́ kan tàbí òmíràn, má lọ́ra láti kàn sí olùdánilẹ́kọ̀ọ́ tàbí àwọn aláṣẹ gẹ́gẹ́ bí ó bá ti yẹ. Abèèrè ọ̀nà ni, kì í ṣìnà.

## 4. 0 ÌGBÉLEWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́

Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan ni ó ní àwọn ìbéèrè ní ìparí wọn, tí wọ́n ní àkọlé ‘Ìṣẹ́ Ṣíṣe’ Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ Ìpín kọ̀ọ̀kan ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kọ̀ọ̀kan ni. Iye Ìpín tí ó bá wà nínú Módù kọ̀ọ̀kan ni iye ìgbéléwọ̀n tí ó wà fún Módù kọ̀ọ̀kan. Mo gbà ọ́ ní ìyànjú kí ó dáhùn gbogbo àwọn ìbéèrè ìnú kọ́ọ̀sì náà pátápátá. Kíyèsí i pe òdíwọ̀n ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún ni máàkì ìgbéléwọ̀n rẹ. Tí àádọ́rin yòókù sì jẹ́ ti ìdánwò àṣekágbá. Ìdí nìyí tí o gbọ́dọ̀ fi múra sí iṣẹ́ ìgbéléwọ̀n náà dáradára, sì rí i dájú pé o fi ìdáhùn rẹ ṣọwọ́ sí olùdánilẹ́kọ̀ọ́ tàbí àwọn aláṣẹ gẹ́gẹ́ bí ó ti tọ́.

## 5. 0 ÌDÁNWÒ ÀṢEKÁGBÁ

Ó pọn dandan láti ka gbogbo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú kọ́ọ̀sì yìí. Gbogbo àwọn ìṣọ̀rí ìsọ̀rí rẹ̀ ni ìbéèrè yóò ti jáde nínú ìdánwò. Gẹ́gẹ́ bí a sì ti sọ tẹ́lẹ̀, ìdá àádọ́rin nínú ọgọ́rùn-ún (70%) máàkì ni a óò gbé gbogbo ìdánwò ìparí kọ́ọ̀sì náà lé. Ìdá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún (30%) yòókù ni yóò jẹ́ ìgbéléwọ̀n àwọn iṣẹ́ inú kọ́ọ̀sì náà tí a fún ọ. Láti gbáradì fún ìdánwò, yóò dára bí ó bá ṣe àtúngbéyẹ̀wò àwọn ìbéèrè Iṣẹ́ ṣíṣe dáadáa, àwọn ìsọníṣókí àti àgbálọgbábọ̀ pẹ̀lú àwọn àkọsílẹ̀ tí o ti ṣe fúnra rẹ. Ìwọ̀nyí yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ púpọ̀púpọ̀. Mo gbà ọ́ ní ìyànjú pé kí o ka ìbéèrè dáadáa kí o tó dáhùn rẹ̀ ní àkókó ìdánwò, kí o sì fi iyè sí àwọn ọ̀rọ̀ ìtọ́sọ́nà àti àkíyèsí orí ìwé ìbéèrè ìdánwò náà dáradára pẹ̀lú. Mo gbà ọ́ níyànjú pé kí o lo àwọn àpẹẹrẹ tí o ṣàwárí fúnra rẹ ju èyí tí olùkọ́ fún ọ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lọ. Èyí ni yóò fi hàn gbangba wí pé ohun ti o kà yé ọ yékéyéké, pé kì í kàn ṣe pé àkọsórí ni o fi gbogbo ìkẹ́kọ̀ọ́ náà ṣe, tí ó o sì fi rí máàkì tí ó wú gọ́gọ́ gbà.

## 6.0 ÌLÀNÀ MÁÀKÌ GBÍGBÀ

Ìlànà máàkì fún kọ́ọ̀sì yìí:

| | |
|---|---|
| Ìgbéléwọ̀n | Máàkì 30% |
| Ìdánwò ní ìparí kọ́ọ̀sì | Máàkì 70% |
| Àropọ̀ gbogbo máàkì | 100% |

ix

# MÓDÙ 1
# ÌFÁÁRÀ GBOGBOGBÒÒ

## Ìpín 1: Èdè Ìperí

Àkóónú

1. 0 Ìfáárà
2. 0 Èròǹgbà
3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú
4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4. 1 Àgbéyẹ̀wò àwọn èdè ìperí: Eré-oníṣe, eré-onítàn àti tíátà (eré orí-ìtàgé)
4. 2 Ìwọ̀núbọ̀nú ìtumọ̀ àti àmúlò àwọn èdè ìperí náà.
4. 3 Eré oníṣe gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ àti bíi tíátà.
5. 0 Ìsọnísọ́kí
6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7. 0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1. 0 Ìfáárà

Eré kì í ṣe ọ̀rọ̀ àjèjì nínú èdè Yorùbá. Gbogbo ohun tí a bá ń ṣe, tí kì í ṣe iṣẹ́, tí kì í sì í tún ṣe dandan kí á ṣe é, èyí tí à ń lò láti fi najú tàbí láti fi nara; fún ìgbádùn tàbí ìdánilárayá ni Yorùbá kà sí eré. Èyí le jẹ́ àwọn ìṣe gẹ́gẹ́ bí ìjàkadì, ìfò fífò, lílúwẹ̀ẹ́ nínú odò ńlá, ayò títa àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Eré tún le jẹ́ ọ̀rọ̀ ẹnu gẹ́gẹ́ bí àwàdà ṣíṣe, ìyakọ jíjẹ, àlọ́ pípa, àrọ̀ jíjá àti ìmọ́ bíbú. Oríṣìí eré kan ni àwọn ewì alohùn Yorùbá bí orin etíyẹrí, orin àgàsá, orin obitun, ìpohùn eré ọdẹ, tí a mọ́ sí ìjálá, ìpohùn eré àwọn babaláwo, tí a mọ́ sí ìyẹ̀rẹ̀ ifá àti ìpohùn eré àwọn ọ̀jẹ̀, tí a mọ̀ sí ẹ̀ṣà egúngún. Yàtọ̀ sí ẹ̀ṣà pípè, àwọn eléégún aláré tún ní oríṣi ìṣere kan tí à ń pè ní idán. Irú eré/ idán eégún aláré yìí àti àwọn ìṣeré ajẹmórò bíi ti ọdún ìbílẹ̀, àwọn tí wọ́n ti wà ṣaájú kí àwọn òyìnbó tó kó àṣà ọ̀làjú wọn òde-òní dé ni a gbà bí eré àbáláyé tàbí àdáyébá àwọn Yorùbá. Gbogbo àwọn ìṣeré tí wọ́n bẹ̀rẹ̀ lẹ́yìn tí àwọn Òyìnbó dé ọ̀dọ̀ wa ni a kà sí àwọn eré òde òní tàbí ti bágbàmu.

Àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ àmúlò mẹ́ta kan tó ṣe pàtàkì nínú ìjíròrò inú ẹ̀kọ́ yìí ni eré-oníṣe, eré-onítàn àti tíátà. Àwọn ọ̀rọ̀ àmúlò wọ̀nyí jẹ́ àwọn èyí tí a fi túmọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ èdè ìperí kan láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì sí èdè Yorùbá. Ìwọ̀núbọ̀nú tí ó sú yọ láàrin ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ èdè ìperí náà láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì tí a ti túmọ̀ wọn àti nínú èdè Yorùbá tí a túmọ̀ wọn sí jẹ́ ohun tó nílò àlàyé kíkún. Torí náà, àlàyé kíkún nípa àwọn èdè ìperí yìí àti ìtumọ̀ wọn ni ìjíròrò inú ìpín yìí dá lé..

## 2. 0 Èròǹgbà

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ìwọ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ yóò ti lè:

- Ṣe àlàyé ohun ti eré túmọ̀ sí ní ilẹ̀ Yorùbá. Yóò sì ti le ṣe àpẹẹrẹ oríṣìíríṣìí eré Yorùbá.
- Tọ́ka sí àwọn èdè ìperí tí a fi túmọ̀ *drama*, *play* and *theatre* sí èdè Yorùbá.
- Tọ́ka sí àwọn ìwọ̀núbọ̀nú tí ó jẹyọ láàárín àwọn èdè ìperí náà nínú èdè tí a ti túmọ̀ wọn sí inú èdè Yorùbá àti nínú èdè Yorùbá tí a túmọ̀ wọn sí.

- Ṣe àlàyé ohun tí eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ àti eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi tíátà jẹ́.

## 3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú

1. Ṣe àpẹẹrẹ ohun mẹ́ta tí àwọn Yorùbá kà sí eré.
2. Àwọn èdè ìperí wo ni a fi túmọ̀ *drama, play* àti *theatre* sí èdè Yorùbá?
3. Tọ́ka sí àwọn ìwọ̀núbọ̀nú tó wà nínú ìtumọ̀ *drama, play* àti *theatre*
4. Kín ni ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ àti eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi tíátà?

## 4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4. 1 Àgbéyẹ̀wò àwọn èdè ìperí: eré-oníṣe, eré-onítàn àti tíátà

Èdè-ìperí ni èdè tí à ń lò láti fi ṣe àlàyé-ọ̀rọ̀ nínú ẹ̀kọ́ iṣẹ́ tàbí ìmọ̀ kan. Nìgbà tí ó jẹ́ pé ẹ̀kọ́ mọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà yìí kì í ti í ṣe ara àṣà abínibí ilẹ̀ Yorùbá, ó pọn dandan fún wa láti ṣe àwárí àwọn èdè tí a ó máa lò láti ṣe àlàyé ọ̀rọ̀ nínú ẹ̀kọ́ iṣẹ́ ìwé kan tàbí òmíràn (bí àpẹẹrẹ, ẹ̀kọ́ èdè, àṣà, lítíréṣọ̀ àti ìkọ́ni). Nítorí ìdí èyí ni àwọn onímọ̀-èdè fi foríkorí láti ṣe àgbékalẹ̀ àwọn èdè ìperí tí a ó máa fi pe àwọn ọ̀rọ̀ tí a ó fi túmọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ èdè Gẹ̀ẹ́sì tí à ń mú lò nínú ẹ̀kọ́ èdè, àṣà, lítíréṣọ̀ àti ìkọ́ni. Oríṣìíríṣìí akitiyan ni ó ti wáyé lórí èdè ìperí tító di lọ́ọ̀lọ́ yìí. Nínú ìwé *Èdè-ìperí Yorùbá*, eré oníṣe ni a fi túmọ̀ *drama* (ayálò: dírámà), eré onítàn, ni a fi túmọ̀ *play*, a sì yá tíátà lò láti inú *theatre* (tí àwọn mìíràn ń lo eré ìtàgé fún) [*wo Fọlúùmù kìn-ín-ní Èdè-ìperí Yorùbá* o.i. 22, 60 àti 84]. Ó yẹ kí á tọ́ka sí i ní ọ̀gangan ibi tí a dé yìí pé ìtumọ̀ àwọn èdè ìperí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ́nyí gbẹ́nu le ara wọn. Èyí sì fẹ́rẹ̀ mú àmúlùmálà ìtumọ̀ wà láàárin wọn. Ní báyìí, ẹ jẹ́ ká fi àwọn ìwọ̀núbọ̀nú ìtùmọ̀ tó wà ní àárín wọn hàn.

### 4. 2 Ìwọ̀núbọ̀nú, ìtumọ̀ àti àmúlò àwọn èdè ìperí náà

- Ìwọ̀núbọ̀nú àárín àwọn èdè ìperí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí ti fara hàn láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì tí a ti mú wọn lò. Ìyẹn ni pé, ìtumọ̀ *drama, play* àti *theatre* nínú èdè Gẹ̀ẹ́sì gan-an náà gbé wọnú ará wọn

- Ní àkọ́kọ́, gbogbo *play* (eré-onítàn), yálà a kọ wọ́n sínú ìwé tàbí a ṣe wọ́n lórí ìtàgé, sinimá, rédíò, tẹlifíṣàn, tàbí ìwé eré onífọ́tò, ni àwọn Gẹ̀ẹ́sì máa ń pè ní *drama*

  (eré-oníṣe). Bí ìṣẹ̀lẹ̀ kan bá sì tún ṣẹlẹ̀ láwùjọ tí ó jẹ́ kàyéèfì, wọ́n tún lè sọ pé ó jẹ́ mọ́ eré-oníṣe (pé ó wà *dramatic*) tàbí kí wọ́n tilẹ̀ là á mọ́lẹ̀ pé *drama* (eré-oníṣe) ni.

- *Theatre* (tíátà) ni wọ́n ka gbogbo akitiyan ìṣeré (*performance*) lóríṣìíríṣìí sí. Irú ìṣeré bẹ́ẹ̀ le jẹ mọ́ eré-onítàn, idán onímàjíìkì, orin, ìlù àti ijó abbl. Tíátà yìí kan náà ni wọ́n ń pe àpapọ̀ ìmọ̀ ẹ̀kọ́ tí ó jẹ mọ́ ìṣeré, pàápàá ti ìgbérékalẹ̀ lórí ìtàgé. Bí ìṣẹ̀lẹ̀ kan bá pani lẹ́rìn-ín tàbí tí ó jẹ́ kàyéfì wọn a máa sọ pé ó jẹ mọ́ tíátà ( pé ó wà theatrical)

tàbí kí wọ́n tilẹ̀ sọ pé *theatre* ni. *Theatre* (tíátà)náà ni wọ́n tún ń pe gbọ̀ngàn ilé ìwòran eré (àti àwọn gbọ̀ngàn iṣẹ́ mìíràn náà pàápàá). Èyí tí ó kan àwa gbọ̀ngbọ̀n níbí ni bí wọ́n ṣe ń pe eré orí-ìtàgé (eré onítàn tí a gbe kalẹ̀ lórí ìtàgé; *staged play*) ní eré-oníṣe nígbà mìíràn tí wọ́n á sì tún pè é ní tíátà nígbà mìíràn. Ohun kan tí a fẹ́ pe àkíyèsí sí ni pé bogbo ìwọ̀núbọ̀nú tí ó súyọ láàrín ìmúlò *play*, *drama* àti *theatre* ní ẹ̀dẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì náà ló fara hàn nínú àwọn ìmúlò àwọn ọ̀rọ̀ èdè ìperí eré-onítàn, eré-oníṣe àti tíátà tí a fi túmọ̀ wọn sí èdè Yorùbá

- Gẹ́gẹ́ bí a ti tọ́ka sí i lókè, ìtumọ̀ "eré" ní èdè Yorùbá gbòòrò gan-an. Èré le jẹ́ orin, ìlù àti ijó, àwàdà àti àpárá, eré ìdárayá: tìta-gbangba, (bíi òkìtì títa àti ẹkẹ tàbí ẹ̀mù mímù, tí a tún mọ̀ sí ìjàkadì jíjà) tàbí eré ìdárayá tabẹ́lé bíi ayò ọlọ́pọ́n, lúdò tàbí káàdì títa àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ). Eré náà ni iṣẹ́ àwọn oníṣẹ́-ọnà alohùn bíi ìjálá, ẹ̀sà, rárà, olele, ègè, ẹkún ìyàwó, alámọ̀, àṣamọ̀ abbl (kíyèsi pé ìjálá ni eré Ògún/ eré ọdẹ; eléégún aláré ni orúkọ mìíràn fún àwọn ọ̀jẹ̀ apidán.)
- Láti pe àkíyèsí sí pàtàkì ìṣe nínú àwọn eré kan ni a fi sọ "oníṣe" mọ́ "eré" tí ó fi fún wa ní "eré-oníṣe" tí a fi túmọ̀ *drama*. Láti pe àkíyèsí sí ṣíṣe pàtàkì àhunpọ̀-ìtàn nínú àwọn eré tí ó ní ìtàn nínú ni a ṣe sọ "onítàn" mọ́ "eré" láti fún wa ní "eré onítàn," tí a fi túmọ̀ *play*. Bákan náà ni ó sì jẹ́ pé láti tọ́ka sí ṣíṣe pàtàkì ìtàgé nínú àwọn eré tí a gbé kalẹ̀ lórí ìtàgé ni a ṣe sọ "ìtàgé" mọ́ "eré" láti fún wa ní "eré (orí) ìtàgé." Ó yẹ kí á pe àkíyèsí sí i wí pé ìgbíyànjú láti pààlà sáàrin oríṣiríṣi àwọn eré náà ni àwọn akitiyan yìí tún ń tọ́ka sí, ṣùgbọn ààlà náà kò ṣe danindanin tó nítorí ìwọ̀núbọ̀nú tí ń bẹ láàrin ìtumọ̀ wọn.
- Ó yẹ kí á tọ́ka sí i wí pé ìtumọ̀ "oní**ṣe**" tí a sọ pọ̀ mọ́ ere lati túmọ̀ *drama* náà jẹ mọ́ "eré orí-ìtàgé" gan-an. Bí "tíátà" bá jẹ́ ì**ṣ**eré tàbí eré onítàn gbígbé kalẹ̀ lórí ìtàgé, a jẹ́ pé ìwọ̀núbọ̀nú kan tún ti súyọ láàrin ìtumọ̀ "tíátà" gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ èdè ìperí àti "eré-oníṣe". Ìdí ni pé ìṣeré kan náà yẹn ni "oníṣe" inú "eré-oníṣe" ń tọ́ka sí .gẹ́gẹ́ bí ìtumọ̀ sílébù **ṣe** ibẹ̀ ti tóka sí. Sílébù yí kan náà, ni ó wà ní ààrín gbùngbùn ìhun ì**ṣ**eré (lórí ìtàgé) tí ìtumọ̀ tíatà ń dúnnu mọ́. Torí náà, ọ̀rọ̀ tí a fi túmọ̀ *drama* sí Yorùbá tún jẹ́ kí á rí ìwọ̀núbọ̀nú ààrín àwọn èdè-ìperí méjèèjì yẹn (*theatre* àti *drama*) kedere sí i ni.

- Nígbà tí a  wo orísun *drama* (eré-oníṣe) láti inú èdè Gíríìkì (*drameon*), a rí i pé ìṣe (*action* , ìṣe) ni ó túmọ̀ sí. Ìdí tí àwọn onímọ̀ fi túmọ̀ rẹ̀ sí eré-oníṣe (eré tí ó ní ìṣe nínú) nìyẹn. Àwọn onímọ̀ tí ó túmọ̀ ọ̀rọ̀ náà kò rokàn irúfẹ́ ìwọ̀núbọ̀nú tó súyọ yìí. Ó yẹ kí a lo àǹfàní yìí láti pe àkíyèsí sí i pé *theatron* láti inú èdè Gíríìkì ni orísun *theatre* ní èdè Gẹ̀ẹ́sì; gbọ̀ngàn ìṣeré tàbí ojú agbo ìṣeré sì ni ìtumọ̀ rẹ̀. Kò yà wá lẹ́nu nígbà náà pé gbọ̀gàn ìṣeré jẹ́ ìkan lára àwọn ìtumọ̀ tí *theatre* ṣi ní lóde òní bí ìjíròrò wa ìṣaájú ti fi hàn.  Bí a ti fi hàn ṣáájú ìtumọ̀ tí *theatre* bí èdè ìperí ní lónìí ti jù bẹ́ẹ̀ lọ.
- Ìtumọ̀ tí àwọn onímọ̀ máa ń fún àwọn ọ̀rọ̀ èdè ìperi mẹ́ta tí a jíròrò lé lórí tí a óò sì ṣàmúlò ni ìwọ̀nyí:
    - Eré-onítàn: Èyí ni gbogbo eré tí a bá fi ṣe àgbekalẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn kan tàbí òmíràn.
    - Eré-oníṣe: Èyí ni eré gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ àti ẹ̀kọ́ ìmọ̀ kan. Eré-onítàn àpilẹ̀kọ nìkan ni àwọn onímọ̀ láti òkè okun máa ń ni lọ́kàn tí wọn bá ń sọ̀rọ̀ eré-oníṣe, ṣùgbọ́n àwa ní ilẹ̀ Afíríkà àti pàápàá ilẹ̀ Yorùbá, tí ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà wa ṣẹ̀ṣẹ̀ ń fẹsẹ̀ múlẹ̀, a kò lè fara mọ́ èyí, àyàfi bí a óò bá gbà pé a kò níí ní eré-oníṣe ṣaájú kí àwọn òyìnbó tó kó àṣà ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà dé nìkan ló kù.
    - Tíatà: Èyí ni gbogbo ìṣeré lórí ìtàgé/ ojú agbo eré àti ẹ̀kọ́ ìmọ̀ rẹ̀.

## 4. 3 Eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ àti bíi tíátà

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn onímọ̀ gbìyànjú láti pààlà sí àárín àwọn èdè ìperí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀n-ọn-nì síbẹ̀ àmúlò wọn fi hàn gedegbe pé ìtumọ̀ wọn wọnú ara wọn. Nínú ẹ̀kọ́ yìí, bí ó tiẹ̀ jẹ́ pe ọ̀rọ̀ eré-oníṣe ni ó jẹ wá lógún jùlọ, síbẹ̀ a kò lè dijú sí ọ̀rọ̀ tíátà. Ìdí ni pé àpilẹ̀ṣe ni àwọn eré àbáláyé tí a ó gbé yẹ̀wò. Púpọ̀ nínú àwọn eré ìgbàlódé bí i ti Ogunde, Kọ́lá Ògúmọ̀lá Akin Ògúngbè, Dúró Ladipọ, Moses Ọláìyá Adéjùmọ̀ abbl. tí a óò tún gbé yẹ̀wò náà ni wọ́n tún jẹ́ àpilẹ̀ṣe. Tíátà ni jíjẹ́ àpilẹ̀ṣe yìí ń tọ́ka sí. Nítorí náà bí a óò ti máa sọ̀rọ̀ nípa eré-oníṣe bíi lítíréṣọ̀, náà ni a óò máa sọ̀rọ̀ nípa eré-oníṣe bíi tíátà tàbí ìṣeré. Ìsínjẹ jẹ́ àbùdá tí ó kó gbogbo iṣẹ́ ọnà pọ̀. Nítorí náà, ìbáà ṣe eré-oníṣe bíi lítíréṣọ̀ tàbí  bíi tíátà ìsínjẹ a máa jẹ yọ nínú wọn.

Nínú àgbéyẹ̀wò eré oníṣe gẹ́gẹ́ bí i lítíréṣọ̀, ìbáà ṣe tàpilẹ̀kọ tàbí tàpilẹ̀ṣe (tí a tún lè pè ní ti alohùn), àwọn àbùdá ajẹmọ́lítíréṣọ̀ níí máa ṣe pàtàkì jùlọ. Àpẹẹrẹ àwọn àbùdá bẹ́ẹ̀ ni ìfìwàwẹ̀dá, àhunpọ̀ ìtàn, kókó ọ̀rọ̀, ẹ̀dá ìtàn àti ìfìwàwẹ̀dá wọn, ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì pẹ̀llú àmúlò èdè abbl. Ẹ̀wẹ̀, bí a bá ń sọ̀rọ̀ eré oníṣe gẹ́gẹ́ bíi tíátà, àbùdá ìṣeré bí i òṣèré, ìmúra òṣèré, ibi ìṣeré, aṣọ eré, ohun èlò ìṣeré, òǹwòran abbl. ni í máa ṣe pàtàkì jù. Bí ojú méjì tí owó máa ń ní ni ọ̀rọ̀ eré-oníṣe bíi lítíréṣọ̀ àti eré-oníṣe bíi tíátà; wọn kì í ya ara wọn.

## 5. 0 Ìsọníṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí,

- A ṣe àlàyé pé eré-oníṣe ni a fi túmọ̀ *drama*, a fi eré-onítàn túmọ̀ *play* nígbà tí a yá *theatre* lò, tí a pè ní 'tíátà' ní èdè Yorùbá.
- A ṣe àlàyé pé ìtumọ̀ eré fúnra rẹ̀ kò dúró sí ojú kan.
- A tẹ̀ síwájú pé ìwọ̀núbọ̀nú jẹ yọ nínú àwọn ọ̀rọ̀ tí a fi túmọ̀ àwọn èdè ìperí wọ̀nyí sí èdè Yorùbá. A yán an pé, láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì tí a ti yá wọn ni ìwọ̀núbọ̀nú yìí ti kọ́kọ́ fara hàn. A tún fi hàn pé akitiyan ìpàálà gúnmọ́ sáààrín ìtumọ̀ àwọn èdè ìperí wọ̀nyí ṣòroó ṣe.
- A sì tún tọ́ka sí àwọn àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ àti ti eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi tíátà.

## 6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

i. Kí ni èdè ìperí?

ii. Dárúkọ èdè ìperí tí a fi túmọ̀ *drama*, *play* àti *theatre* sí èdè Yorùbá?

iii. Ṣe àlàyé ìwọ̀núbọ̀nú tí ó jẹyọ nínú ìtumọ̀ eré-oníṣe, eré-onítàn àti tíátà?

iv. Dárúko àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ àti eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi tíítà

## 7. 0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adedeji, J. A. 1973. *The Adámù orìṣà play*. Department of Theatre Arts Occasional Pulication, No. 1, University of Ibadan, Ibadan,

Awobuluyi, O. 1991 (Olótùú) *Yorùbá Metalanguage (Èdè-Ìperí Yorùbá)* Vol.II, UPL àti NERDC

Bamgboṣe, A. 1984 (Olótùú) Yorùbá Metalanguage (Èdè-Ìperí Yorùbá) Vol.I, NERDC

Ogundeji, P.A. 1981. The Plays of Oyin Adejọbi: An Introductory Study. Àpilẹ̀kọ fún oyè ìjìnlẹ̀ Ẹ́m-Èè, Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Ibadan o.i. 1-12.

Ogundeji, P.A. 1987. "Trends and Issues in the Ogunde Dramatic Tradition", *Review of English and Literary Studies*, Fol. 4. 1, o.i. 69-94.

Ogundeji, P. A. 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature.* Distance Learning Centre, University of Ibadan, Ibadan, ( o. i. 21 – 22 àti o.i. 126 – 128).

## Ìpín 2: Ìpínsísọ̀rí Gbogbogbòò fún eré-oníṣe Yorùbá

### Àkóónú

1. 0 Ìfáárà

2. 0 Èròǹgbà

3 . 0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4. 1 Ìpínsísọ̀rí alákòókò ìwásáyé

4. 2 Ìpínsísọ̀rí oníṣẹ̀dá

4. 3 Ìṣòro Ìpínsísọ̀rí

5. 0 Ìsọníṣókí

6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7. 0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1. 0 Ìfáárà

ìsọ̀rí ìsọ̀rí tí àwọn eré-oníṣe Yorùbá pín sí ni gbogbogbòò ni ó kan wá gbọ̀ngbọ̀n nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Abala méjì ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí pín sí. Abala àkọ́kọ́ ni a ti ṣe ìpínsísọ̀rí eré, abala èkejì ni a ti ṣàfihàn àwọn ìṣòro tí ó jẹyọ nínú ìpínsísọ̀rí náà.

### 2. 0 Èròǹgbà Àti Àfojúsùn

Nígbà tí o bá ka ìpín yìí tán, o ó le

- Dárúkọ àwọn ìlànà òdiwọ̀n tí a fi ṣe oríṣi ìpínsísọ̀rí eré-oníṣe Yorùbá méjì.
- Ṣe àlàyé àwọn ìpínsísọ̀rí náà ní ṣókí ṣókí.
- Ṣe àlàyé àwọn ìṣòro tí ó jẹyọ láti inú àwọn ìpínsísọ̀rí méjèèjì náà.

### 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Ìlànà òdiwọ̀n wo ni o lérò pé a lè fi ṣe ìpínsísọ̀rí àwọn eré-oníṣe Yorùbá?
2. Ìsọ̀rí ńláńlá mélòó ni o lè fi ìlànà òdiwọ̀n náà pín eré-oníṣe Yorùbá sí? Dárúkọ wọn.
3. Àwọn ìsọ̀rí kéékèké wo ni àwọn ìsọ̀rí ńláńlá náà pín sí?

### 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìpínsísọ̀rí alákòókò ìwásáyé

- Bí a bá lo àkókò ìwásáyé bí òdiwọ̀n, a lè pín eré-oníṣe Yorùbá sí ọ̀nà méjì gbígbòòrò ni. Àkọ́kọ́ ni eré-oníṣe àbáláyé, èkejì sì ni eré-oníṣe òde òní.
- Fún kọ̀ọ̀sì yìí, ọ̀nà kékèké méjì mìíràn tí a tún eré-oníṣe àbáláyé pín sí ni eré-oníṣe ọdún ìbílẹ̀, àti eré-oníṣe eégún aláré.
- A sì tún eré-oníṣe òde-òní pín sí ti onílànà Ogunde ati tí àpilẹ̀kọ.
- Àkókò ìwásáyé nínú ìtàn ilẹ̀ Yorùbá tí a lò bí òdiwọ̀n láti ṣe gbèdéke ààlà ìpínsísọ̀rí náà sí méjì gbẹrẹgẹdẹ bẹ́ẹ̀ ní ìgbà tí àwọn òyìnbó Gẹ̀ẹ́sì gbé àṣà eré-oníṣe ti ilẹ̀ òkèèrè dé ilẹ̀ àwa Yorùbá.
- Àkókò yìí ni ìṣèjọba ìmúnisìn ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì bẹ̀rẹ̀.
- Eré ọdún ìbílẹ̀ àti ti eégún aláré ti wà ṣaájú àkókò yìí. Lẹ́yìn ìgbà tí àwọn Gẹ̀ẹ́sì kó àṣà ìṣeré wọn dé ni eré onílànà Ogunde àti eré-oníṣe àpilẹ̀kọ tó dìdelẹ̀.
- Nítorí náà orúkọ mìíràn tí a tún lè pè eré-oníṣe àbáláyé ni eré-oníṣe aṣaájú ìmúnisìn, a sì lè pe eré-oníṣe òde-òní ní eré-oníṣe ẹ̀yìn ìmúnisìn

## 4. 2 Ìpínsísọ̀rí oníṣẹ̀dá

- Bí a bá lo ìlànà òdiwọ̀n ìṣẹ̀dá àwọn eré náà nígbà tí àwọn olùṣẹ̀dá wọn ń pilẹ̀ tàbí tí wọ́n ń ṣẹ̀dá wọn, ọ̀nà méjì tí àwọn eré-oníṣe Yorùbá tún pín sí ni ti àpilẹ̀ṣe àti ti àpilẹ̀kọ.
- Lábẹ́ eré-oníṣe àpilẹ̀ṣe ni eré-oníṣe ọdún ìbílẹ̀, ti eégún aláré àti ti onílànà Ogunde yóò wà, eré-oníṣe àpilẹ̀kọ nìkan ni yóò sì dá dúró.
- Kò sí àkọsílẹ̀ kankan fún àwọn eré ọdún ìbílẹ̀ àti tí eégún aláré ní àkókò ìpìlẹ̀ tàbí ìṣẹ̀dá wọn nítorí àìsí ìmọ̀-ọ̀n-kọ-mọ̀-ọ̀n-kà ní àkókò náà láàrín àwọn Yorùbá.
- Púpọ̀ nínú eré-oníṣe onílànà Ogunde náà ni a kò kọ sílẹ̀ ní àakókò ìpìlẹ̀ tàbí ìṣẹ̀dá wọn, tí ó jẹ́ pé ìlànà ìṣeré dan-an-wò-ká-rí-i (*improvisation*) ni wọ́n fi gbé wọn kalẹ̀; àpilẹ̀ṣe ni wọ́n.
- Lẹ́yìn tí wọ́n bá ṣe wọ́n tán wọ́n lè ṣe àdakọ ọ̀rọ̀ ẹnu (ìyẹn ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì àárín) àwọn òṣèré tí wọ́n ti ká sínú fọ́n-ọ́n-rán ní àkókò ìṣeré. Síbẹ̀ èyí kò sọ irú eré bẹ́ẹ̀ di àpilẹ̀kọ, eré-oníṣe àdàkọ ni; àpìlẹ̀ṣe náà ṣì ni.

- Láti ìpìlẹ̀ wá, ní àkókò ìṣẹ̀dá, ni eré-oníṣe àpilẹ̀kọ ti jẹ́ kíkọ sílẹ̀ ní tirẹ̀, òun kì í ṣe àpilẹ̀ṣe, lẹ́yìn ìgbà tí òǹkọ̀wé eré-oníṣe (tí ó jẹ́ olùṣẹ̀dá rẹ̀) bá kọ ọ́ tán ni àǹfàní tó wà láti ṣe é ní orí ìtàgé.
- Ohun tí ìpínsísọ̀rí ajẹmọ́ṣẹ̀dá yìí ń tọ́ka sí ni pé gbígbékalẹ̀ lójú agbo eré tàbí ìtàgé bíi tíátà (ìṣeré) ni ohun àkọ́kọ́ nínú àwọn eré àpilẹ̀ṣe mẹ́tẹ̀ẹ̀ta náà, tí kíkọ sínú ìwé sì jẹ́ ohun kejì.
- Ní ìdàkejì, kíkọ sílẹ̀ ni ohun àkọ́kọ́ nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ, nígbà tí ìṣere tàbí ṣíṣe lórí ìtàgé sì jẹ́ ohun kejì.
- Ó hàn gbangba pé ó ṣe é ṣe láti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ nínú eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi tíátà náà, tí ó sì ṣe é ṣe láti wo àwọn àbùdá ìṣeré tàbí tíátà bí ó ṣe fara hàn nínú eré-oníṣe àpilẹ̀kọ.
- Alójúlódì ni ọ̀rọ̀ náà. Ìdí nìyí tó fi jẹ́ pé ìwọ̀núbọ̀nú tó wà láàárín eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi tíátà àti eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ kò ṣé é pààlà sí danindanin.

## 4. 3 Ìṣòro ìpínsísọ̀rí náà

- Àwọn ìṣòro tí ìpínsísọ̀rí àjẹmákòókò ìwásáyé àti ti ajẹmọ́ṣẹ̀dá ní ni ti ìwọ̀núbọ̀nú tí ó wà láàárin àwọn eré-oníṣe náà bí a ti pín wọn.
- Nígbà tí a pe eré kan ní eré-oníṣe àbáláyé, ohun tó yẹ kó jẹ́ ìrètí wa ni pé irúfẹ́ eré bẹ́ẹ̀ kò yẹ kó bá ìgbà mu mọ́ ṣùgbọ́n èyí kò rí bẹ́ẹ̀ rárá. Níṣe ni àwọn eré-oníṣe tí a pè ní tàbáláyé náà tún ṣì ń wáyé ní òde òní, tí wọ́n sì ń ṣe àmúlò àwọn àbùdá tí ó le mú un di ọ̀tun, tí yóò sì fi bá ìgbà òde òní mu.
- Bákan ni àwọn eré-oníṣe tí a pè ní tòde òní. Níṣe ni àwọn náà tún ń ṣe àmúlò àwọn àbùdá eré-oníṣe àbáláyé. Èyí ni ó fa kí àwọn eré méjèèjì (tàbáláyé àti tòde òní) máa yí wọ inú ara wọn.
- Bákan náà ni ọ̀rọ̀ rí nípa ìpínsísọ̀rí ajẹmọ́ṣẹ̀dá. Bí àlàyé wa ti fi hàn, àkọsílẹ̀ ṣì lè wáyé fún eré àpilẹ̀ṣe; àdàkọ ni a sọ pé a máa pe irú eré àpilẹ̀ṣe bẹ́ẹ̀ tí a dà kọ lẹ́yinọ̀rẹyìn.
- Bẹ́ẹ̀ náà ni ṣíṣeré àpilẹ̀kọ lórí ìtàgé a máa wáyé dáadáa lẹ́yìnọ̀rẹyìn tí eré bá ti di kíkọ sílẹ̀ tán, bí a ti ṣalàyé ṣaájú. Ìwọ̀nyí ló tọ́ka sí ìwọnúbọnú àárín wọn gedegbe.

- Àìsí iṣẹ́ púpọ̀, pàápàá àdàkọ, lórí àwọn eré-oníṣe àbáláyé tún jẹ́ ìṣòro kan gbòógì. Adédèjì (1973) nìkan ni a mọ̀ ti ó gbìyànjú láti ṣe àdàkọ ọdún Ẹ̀yọ̀ ní ìlú Èkó gẹ́gẹ́ bí eré-oníṣe, ṣùgbọ́n iṣẹ́ náà kò sí lárọ̀ọ̀wọ́tó mọ́. Ọ̀jọ̀gbọ́n Oyin Ògúnbà (1967) náà ti ṣe ìṣẹ́ lórí àwọn ọdún ìbílẹ̀ Ìjẹ̀bú, nínú èyí tí a ti rí àpèjúwe ìṣeré àwọn ọdún ìbílẹ̀ náà. Àránsí (2016) náà ṣe irú iṣe bẹ́ẹ̀ lórí ọdún Igogo ní Ọ̀wọ̀, Fáséhùn (2017) sì ṣe tirẹ̀ lórí ọdún Ọ̀ràmfẹ̀, Ògún àti Ọba ní Oǹdó. Àwọn àpèjúwe ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ inú iṣẹ́ àwọn onímọ̀ yìí ràn wá lọ́wọ́ láti tan òye ìmọ́lẹ̀ díẹ̀ sí àwọn àbùdá eré-oníṣe ọdún ìbílẹ̀.
- Àìsí ọ̀pọ̀lọpọ̀ irúfẹ́ àdàkọ àti àpèjúwe kíkún bẹ́ẹ̀ lórí àwọn eré odún ìbílẹ̀ báyìí kò ṣèrànwọ́ fún níní ìmọ̀ kíkún nípa ọdún ìbílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí eré-oníṣe. Púpọ̀ nínú àwọn iṣẹ́ àtúpalẹ̀ alápèjúwe ni wọ́njẹ́ iṣẹ́ àṣegboyè tí kò sí lárọ̀ọ̀wọ́tó mọ́. Gbogbo ìwọ̀nyí ni kò fi àyè gbà wá láti ní òye kíkún nípa ìrísí àti ìwúlò ọ̀pọ̀lọpọ̀ àbùdá irú eré-oníṣe náà dáradára. Bí a bá ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpèjúwe àti àdàkọ irúfẹ́ àwọn eré-oníṣe yìí ni, ìmọ̀ wa ì bá kún ju bí ó ṣe wà lọ nípa àwọn eré-oníṣe àbáláyé.
- Àwọn àdàkọ díẹ̀ wà fún eré-oníṣe onílànà Ogunde, ṣùgbọ́n wọn kò tó rárárárá, bí a bá fi ojú inú wo bí eré-oníṣe náà ti pọ̀ tó. Eré òde-òní tí òun jẹ́ ni a lérò pé ó jẹ́ kí ó rọrùn díẹ̀ ju ti àbáláyé lọ; àti wí pé a ní àǹfàní ìṣàmúlò àwọn àgbàsílẹ̀ àwọn eré onílànà Ogunde yìí ní orí ẹ̀rọ tẹlifíṣàn, rédíò, àwo rẹ́kọ̀ọ̀dù àti ìwé eré onífọ́tò. Púpọ̀ nínú eré-oníṣe àwọn òṣèré tó tẹra mọ́ ìlànà ìṣeré yìí ni a kò rí àwọn àkọsílẹ̀ eré wọn náà rárá.
- Kò sí àní ànì pé àbùdá eré-oníṣe bíi lítíréṣọ̀ (àpilẹ̀kọ) ń fara hàn nínú eré-oníṣe bíi tíátà (ìṣeré); àbùdá eré-oníṣe bí tíátà náà a sì máa fara hàn nínú eré-oníṣe bíi lítíréṣọ̀ bí a ti yán an tẹ́lẹ̀.
- Ohun mìíràn tí ó tún fa ìṣoro ìpínsísọ̀rí eré-oníṣe Yorùbá, pàápàá ti onílànà Ogunde ni bí ìyípadà kánmọ́kánmọ́ ṣe máa ń dé bá àwọn eré-oníṣe náà àti ìṣeré wọn. Gbogbo àwọn ìyípadà tí ó sì ń wáyé náà ni a gbọ́dọ̀ kọbi ara sí nínú ṣiṣe ìpínsísọ̀rí tó mọ́yán lórí.

## 5. 0 Ìsọníṣókí

- Oríṣi ìpínsísọ̀rí eré-oníṣe Yorùbá méjì ni a dá lábàá: alákòókò ìwásáyé àti oníṣẹ̀dá.

- Ìgbà tí àwọn aṣèjọba ìmúnisìn Gẹ̀ẹ́sì kó àṣà ìṣeré wọn dé ni a fi ṣe gbèdéke ìpínsísọ̀rí alákòókò ìwásáyé; nígbà tí a lo ìṣẹ̀dá ìpìlẹ̀ àwọn eré-oníṣe náà fún ìpínsísọ̀rí oníṣẹ̀dá.
- Ìsọ̀rí méjì méjì gbígbòòrò ni  ìpínsísọ̀rí kọ̀ọ̀kan. a.) Alákòókò ìwásáyé: i.) Àbáláyé àti ii.) Òde-òní; b.) Oníṣẹ̀dá: i.) Àpilẹ̀ṣe àti ii.) Òde òní.
- Àwọn eré-oníṣe àbáláyé náà ni a dà pè ní ti aṣaájú ìmúnisìn, tí a sì da ti òde òní pè gẹ́gẹ́ bí ti ẹ̀yìn ìmúnisìn.
- Àwọn eré-oníṣe Yorùbá méjì tí a kó sábẹ́ eré-oníṣe àbáláyé ni ti ọdún ìbílẹ̀ àti ti eégún aláré; nígbà tí a kó ti onílànà Ogunde àti ti àpilẹ̀kọ sábẹ́ ìsọ̀rí eré-oníṣe òdeòní.
- Nínú ìpínsísọ̀rí oníṣẹ̀dá, eré-oníṣe Yorùbá mẹ́ta tí ó wà lábẹ́ ìsọ̀rí àpilẹ̀ṣe ni ọdún ìbílẹ̀, eégún aláré àti onílànà Ogunde. Eré-oníṣe àpilẹ̀kọ dá wà ní ìsọ̀rí kan ní tirẹ̀ ni.
- Ìṣòro pàtàkì tí ó ń kojú àwọn ìpínsísọ̀rí tí a dá lábàá ni ìwọ̀núbọ̀nú àárín àwọn eré-oníṣe tí n bẹ lábẹ́ wọn, àìsí ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ àdàkọ àti alápèjúwe àti àyípadà òrèkóòrè.

Àwọn àtẹ onígi ìsàlẹ̀ yìí fi ìpínsísọ̀rí eré-oníṣe tí a jírọ̀rò lókè yẹn hàn ní ṣókí.




**Àtẹ ìpínsísọ̀rí alákòókò ìwásáyé** (A ṣàmúlò Ògundèjì 1992)




**Àtẹ ìpínsísọ̀rí oníṣẹ̀dá** (A ṣàmúlò Ògundèjì 192:13)

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

i. Ṣe àlàyé àwọn òṣùwọ̀n òdiwọ̀n méjì tí a lò fún ìpínsísọ̀rí eréoníṣe Yorùbá?

ii. Ṣe ìdámọ̀ àwọn ìsọ̀rí ńlańlá méjì méjì tí a pín eré-oníṣe Yorùbá sí pẹ̀lú ìsọ̀rí kéékèké tí ó wà lábẹ́ wọn.

iii. Jíròrò lórí ìṣòro ìpínsísọ̀rí eré-oníṣe Yorùbá?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adedeji, J. A. 1973. *The Adámù orìṣà play*. Department of Theatre Arts Occasional Pulication, No. 1, Universityf Ibadan, Ibadan,

Aransi, A. O. 2016 *Ojú Àmúwayé Yorùbá ní Ìlànà Eré-oníṣe Nínú Ọdún Igogo ní Ìlú Ọ̀wọ̀,* Spectrum Books Limited, Ibadan.

Awobuluyi, O. 1991 (Olótùú) *Yorùbá Metalanguage (Èdè-Ìperí Yorùbá)* Vol.II, UPL àti NERDC

Bamgboṣe, A. 1984 (Olótùú) *Yorùbá Metalanguage (Èdè-Ìperí Yorùbá)* Fol. I, NERDC

Fasehùn. M. A. 2017 Dramatic Features in Ogun, Oramfe and Oba Festivals of Ondo Kingdom, Nigeria, Unpublished Ph.D. Thesis, University of Ibadan, Ibadan.

Ogundeji, P. A. 1981. The Plays of Oyin Adejọbi: An Introductory Study. Àpilẹ̀kọ fún oyè ìjìnlẹ̀ Ẹ́m-Èè, Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Ibadan o.i. 1-12.

Ogúnbà, O. 1967. Ritual Drama of the Ijẹbu People: A Study of Indigenous Festivals. Unpublished Ph. D. Thesis, University of Ibadan.

Ogundeji, P. A. 1987. "Trends and Issues in the Ogunde Dramatic Tradition", *Review of English and Literary Studies*, Fol. 4. 1, o.i. 69-94.

Ogundeji, P. A. 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature.* Distant Learning Centre, University of Ibadan, Ibadan, (o. i. 21 – 22 àti o. i. 126 – 128).

Ogundeji, P. A. 1992. *Yorùbá Drama 1(Eré-oníṣe Yorùbá 1*). Ibadan: Centre for External Studies University of Ibadan, Ibadan.


## Ìpín 3: Àbùdá Eré-oníṣe Gẹ́gẹ́ bíi Tíátà (ìṣeré)

Àkóónú

1. 0 Ìfáárà
2. 0 Èròǹgbà
3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú
4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4. 1. 0 Àwọn àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi tíátà (ìṣeré)
4. 1. 1 Ìsínjẹ/ Ìsínnijẹ
4. 1. 2 Aṣèsínjẹ
4. 1. 3 Òǹwòran
4. 1. 4 Ibi ìṣeré
4. 1. 5 Aṣọ-eré
4. 1. 6 Ìbòjú àti àwọn ohun èlò ìṣeré mìíràn
4. 1. 7 Orin, Ìṣàré, Ìlù àti Ijó
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáárà

Láti jẹ́ kí òye ohun tí eré-oníṣe jẹ́ yéni dáadáa yóó dára bí a bá ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá rẹ̀. Ọ̀nà méjì ni àwọn àbùdá wọ̀nyí pin sí àwọn ìjíròrò wa ìṣaájú ti fi hàn. Àkọ́kọ́ ni tèyí tí ó jẹ mọ́ tíátà tàbí ìṣeré, ìkejì sì ni ti àwọn tí ó jẹ mọ́ lítíréṣọ̀. Nínú ìdánlẹ́kọ̀ọ́ inú ìpín kẹta yìí àwọn àbùdá ajẹmọ́ tíátà tàbí ìṣeré yẹn ni ó jẹ wá lógún nńú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú ìpín kẹta kọ́ọ̀sì yìí.

## 2.0 Èròǹgbà

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìwọ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ yóó ti lè:

- Dárúkọ àwọn àbùdá eré-oníṣe ajẹmọ́ tíátà.
- Ṣe àlàyé nípa àwọn àbùdá náà
- Ṣe àpẹẹrẹ àwọn àbùdá náà.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

i. Kín ni àbùdá?

ii. Dárúkọ àbùdá eré-oníṣe mẹ́rin tí o mọ̀.

iii. Ṣe àlàyé wọn ní ṣókí ṣókí pẹ̀lú àpẹẹrẹ mejì méjì ó kéré tán.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

## 4.1. 0 Àbùdá eré-oníṣe bíi tíátà (Ìṣere)

- Nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa àbùdá nǹkan à n sọ nípa ọmọlẹ̀/wúnrẹ̀n/ fọ́n-ọ́n-ran/ ohun àdámọ́/ ẹ̀yà ara tàbí ìwúlò nǹkan náà tí a lè fi ṣe ìdámọ̀ rẹ̀; tí ó pààlà sí ohun náà àti àwọn irúfẹ́ rẹ̀ míràn.
- Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé ọ̀rọ̀ eré-oníṣe bí ó ti jẹ mọ́ tíátà ni a ní lọ́kan àwọn àbùdá àdámọ́ àti àdámọ̀ tí a óò máa gbé yẹ̀wò ni ìsínjẹ/ìsínnijẹ, òṣèré, òǹwòran, ibi ìṣeré, aṣọ eré àti ìmúra, ìbòjú àti àwọn ohun èlò ìṣeré mìíràn, orin kíkọ, ìṣàré, ìlù lílù àti ìjó jíjó.

## 4. 1. 1 Ìsínjẹ/ìsínnijẹ

- Ìsínjẹ (tàbí ìsínnijẹ) ni òlú àbùdá, àbùdá ìpìlẹ̀ tàbí tàkọ́kọ́, tó ṣe pàtàkì jù lọ nínú eré-oníṣe, yálà eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ tàbí eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi tíátà. Gbogbo àwọn àbùdá yòókù ni ó rọ̀ mọ́ ọn.
- Ìsínjẹ yìí ni àbùdá eré-oníṣe tí ó kó gbogbo àbùdá yòókù sòdí. Nínú gbogbo iṣẹ́ ọnà, yálà ó jẹ́ eré-oníṣe tàbí kì í ṣe eré-oníṣe ni ìsínjẹ ti ṣe pàtàkì, ṣùgbọ́n nínú eré-oníṣe ni ó ti peléke jùlọ.
- Ìsínjẹ ni kí òṣèré máa ṣe ìfarawé bí ẹ̀dá ìtàn tí à ń sínjẹ ti máa ń ṣe gẹ́lẹ́. Ẹ jẹ́ kí á ti ibi eré-oníṣe àbáláyé mú àlàyé ohun tí ìsínjẹ jẹ́. Nínú ìṣeré orò ọdún ìbílẹ̀ àwọn ẹlẹ́gùn/abọrẹ̀/arẹ̀kú/bàbálórìṣà/ìyálórìṣà/arugbá abbl. máa ń ṣe ìsínjẹ àwọn òrìṣà, baba ńlá àti ìyá ńlá tí ọdún ìbílẹ̀ tí à ń ṣe ọdún wọn dá lé.
- Nínú idán eégún aláré, àwọn òṣèré eégún aláré máa ń sín oríṣìíṣìí àwọn abirùn jẹ láti ṣe ìgbékalẹ̀ eré/idán tó jẹ mọ́ wọn. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, wọ́n máa ń ṣe ìsínjẹ ẹlẹ́ẹ̀kẹ́ dìǹdì, elétí ehoro, eléyín wanbọ abbl. (wo Adédèjì, 1978 àti Ògúndèjì, 1991, 1992, 2000 àti 2014 fún àlàyé kíkún). Nínú eré-oníṣe òde òní, àwọn òṣèré máà ń gbé àbùdá onírúurú ẹ̀dá tó wà ní àwùjọ wọ̀ láti le ṣe ìsínjẹ ìrísí, ìṣesí àti ìhùwàsí wọn bí a bá ṣe gbé wọn kalẹ̀ nínú ìfìwàwẹ̀dá ìtàn inú eré-ónítàn tí wọ́n bá ń ṣe.
- Gbogbo àwọn àbùdá ìṣeré yòókù ní ó ní í ṣe pẹ̀lú ìsínjẹ lọ́nà kan tàbí òmíràn.

## 4. 1. 2 Aṣèsínjẹ

- Oríṣi òṣèré/ eléré kan, ìṣọkùnrin ìṣobìnrin, tí ó jẹ́ akópa ẹ̀dá ìtàn kan tàbí òmíràn nínú ìṣeré ni aṣèsínjẹ; irú eré bẹ́ẹ̀ ìbáà jẹ́ ti àbáláyé tàbí ti òde òní,
- Gbogbo àwọn tí ń kópa kan tàbí òmíràn nínú ìṣeré ni òṣèrè tàbí aláré; ìbáà jẹ́ onílù, oníjo, olórin , apohùn, tàbí olókìtì àti aṣèsínjẹ náà.
- Ipa tí aṣèsínjẹ máa ń kó tí ó mú un yàtọ̀ gedegbe sí àwọn òṣèré/ akópa/ eléré yòókù ni ṣíṣe ìsínjẹ ẹ̀dá ìtàn inú eré-oníṣe bí a ti ṣe sọ. Ní àkókò ìṣeré, ní ibi ìṣeré ni aṣèsínjẹ ti máa ń ṣèsínjẹ fún àwọn òǹwòran láti wò.
- Ó yẹ kí á pe àkíyèsí sí i pé ìyàtọ̀ wà láàrin aṣèsínjẹ àti ẹ̀dá ìtàn. Ẹni tí ó ń kópa gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ìtàn ní àkókò ìṣeré ni aṣèsínjẹ, nígbà tí ó jẹ́ pé ẹni tí aṣèsínjẹ ń sín jẹ ni ẹ̀dá ìtàn.
- A lè fi ojú aṣèsínjẹ wo àwọn abọrẹ̀, arugbá, ẹlẹ́gùn, arẹ̀kú, arugi, babalórìṣà àti ìyálórìṣà, ọba, ìjòyè abbl. nínú ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ níwọ̀n ìgbà tí ó bá ti jẹ́ pé ẹ̀dá ìtàn ìwáṣẹ̀ tàbí akọni ìgbàanì kan tí ó rọ̀ mọ́ orò ọdún ìbílẹ̀ tí wọ́n ń ṣe ni wọ́n dúró fún tàbí tí wọ́n ń sín jẹ ní àkókò ìṣeré. Irú ẹ̀dá ìtàn bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ ẹ̀mí àìrí nígbà míràn bí a ti sọ tẹ́lẹ̀.
- Bí àpẹẹrẹ, ni àkókò tí ẹ̀gùn bá gun ẹlẹ́gùn òrìṣà ní àkókò ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ orìṣà kan, tí gbogbo àwọn apohùn sì ń fi oríkì òrìṣà náà ki ẹlégùn, ìsínjẹ orìṣà náà ni ẹlẹ́gùn yẹn ṣe gẹ́gẹ́ bí àṣèsínjẹ ajẹmórò ọdún ìbílẹ̀ náà. Àkókò tí ẹ̀gùn bá gun aṣèsínjẹ bẹ́ẹ̀ ni a lè sọ pé ìsínnijẹ náà dé góńgó jù lọ.
- Bákan náà, aṣèsínjẹ ni àwọn eléégún aláré tí ó máa ń pidan lójú agbo eré. Àwọn apidán wọ̀nyí ni ó máa ń ṣe ìsínjẹ oríṣiríṣi àwọn ẹ̀dá ìtàn, bíi Àrọ̀nì, Ṣàngó, Tápà, Jagunjagun Ìdàhọ̀mì, Òyìnbó, Gàǹbàrí, eléyín wanbọ, elétí ehoro abbl. fún ìgbádùn àwọn òǹwòran wọn lójú agbo eré.
- Nínú ìṣeré-onítàn àwọn eléré onílànà Ogunde, aṣèsínjẹ ni àwọn bíi Dúró Ladipọ̀ tí ó ṣe ìsínjẹ aláàfin Ṣàngó nínú eré-onítàn *Ọba Kò So,* Moses Ọláìyá Adéjùmọ̀ tí ó ṣe ìsínjẹ, Bàbá Sàlá nínú ọ̀wọ́ eré-onítàn orí tẹlifíṣàn tí àkọlé rẹ̀ ń jẹ́ *Aláwàdà* Kàrímù Adépọ̀jù tí ó ṣe ìsínjẹ Bàbá Wándé nínú ọ̀wọ́ eré-oníṣe tẹlifíṣn tí àkọlé rẹ̀ ń jẹ́ *Kóòtù Aṣipa,* Funnkẹ́ Akíndélé ni aṣèsínjẹ tí ó ṣe ìsínjẹ Sùlíá-Jẹ́nífà nínnú sinnimá àgbélẹ́wò *Jẹ́nífà I àti II.*

- Nínú ìṣeré eré-oníṣe àpilẹ̀kọ *Ẹfúnṣetan Aníwúrà:Ìyálóde Ìbàdàn* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ tí wọ́n ṣe ní Liberty Stadium, Ìbàdàn ni ọdún 1984, Ìṣọ̀lá Ògúnṣolá ni aṣèsínjẹ tí kópa Ìtáwuyì, Ìyábọ̀ Ògúnṣọlá ni ó ṣèsínjẹ Ẹfúnṣetán nígbà tí ó jẹ́ pé Samson Elúwọlé (Jìnádù) ni ó sì kópa Àrẹ Látòósà.

## 4. 1. 3 Òǹwòran

- Àkójọpọ̀ àwọn èniyàn tí ó péjúpésẹ̀ ní ibi ìṣeré láti wo ìsínjẹ ìṣẹ̀lẹ̀ inú àhunpọ̀-ìtàn tí àwọn òṣèré ń ṣe ni òǹwòran eré jẹ́.
- Ìkópa òǹwòran nínú ìṣeré eré-oníṣe àbáláyé máa ń lóòrìn ju ti inú ìṣeré òde òní lọ.
- Oríṣìí òǹwòran méjì ló wà fún ìṣeré eré-oníṣe àbáláyé. Àkọ́kọ́ ni àwọn awo, tí òye àwọn àmì àrokò inú ìṣeré náà yé. Èkejì ni àwọn ọ̀gbẹ̀rì tí wọ́n kàn lọ wòran, tí àwọn òye ìjìnlẹ̀ inú eré kò yé dàradára
- Àwọn òǹwòran nínú ìṣeré àbáláyé ní àǹfàní láti fi ìmọ̀sílára wọn nípa ìṣeré lójú agbo eré, nípa ijó jíjjó, orin gbígbè àti nínáwó fún àwọn òṣèré. Ìwọ̀nba ni ìmọ̀sílára tí òǹwòran lè fi hàn ní gbọ̀ngàn ìsẹ̀ré òde òní; kì í sábàá ju kí a pàtẹ́wọ́ fún òṣeré lọ àti bóya kí wọ́n bá wọn gberin lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan.

## 4. 1. 4 Ibi ìṣeré

- Ibi ìṣeré ni ọ̀gangan àyè/ ibi tí a ti gbé eré kalẹ̀, tàbí tí ìṣeré tí wáyé.
- Oríṣìí ibi ìṣeré gbígbóórò mejì ló wà: olójúkojú àti àìjólójúkojú.
- Ti olójúkojú ni ibi tí òṣèré àti òǹwòran ti ní àǹfàní láti ri ara wọn ní ojúkorojú, ti àìjólójúkojú ni ibi tí òṣèré àti òǹwòran kò ti ní àǹfàní láti fi ojú rinjú.
- Níbi ìṣeré àìjólójúkojú, àwọn òǹwòran lè ni àǹfàní láti gbọ́ ohùn òṣèré (lorí rédíò, àwo rẹ́kọ̀ọ̀dù, téèpù oníkásẹ́ẹ̀tì, tàbí síídiì olóhùn) wo àwòrán alèrìn òṣèré kí wọn sì gbọ́ ohùn rẹ̀ papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà (tẹlifíṣàn, sinimá, fídíò) tàbí kí wọ́n wo àwòrán àìlèrìn àwọn òṣeré nínú ìwé eré onífọ́tọ̀ kí wọ́n sì ka ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì wọn; ṣùgbọ́n wọn kò ní àǹfànní láti fi ojú rinjú pẹ̀llú òṣèré.

- Ibi ìṣeré olójúkojú nínú eré-oníṣe àbáláyé lè jẹ́ ojútáyé níbi tí gbogbogbòò tàbí tawotọ̀gbẹ̀rì ti lè rí ara wọn ní ojúkorojú, ó sì tún lè jẹ́ ibi ìpamọ́ tàbí kọ̀lọ́fín, níbi tí ó jẹ́ pé àwọn awo nìkan níí máa jẹ́ akópa, yálà bí òṣèré tàbí òǹwòran (b.a. inú ilé awo, igbó imọ̀lẹ̀, igbó orò, ìgbàlẹ̀ eégún abbl.).
- Nínú ìṣeré àbáláyé ibi ìṣeré ojútáyé lè jẹ́ ojú agbo eré, ní ojúde ọba tàbí tìjòyè, ojú ọjà, òpópónà eré tàbí ibi ìyàsọ́tọ̀ mìíràn tí ó jẹ́ gbàgede. Ìṣeré òde òní náà lè ṣàmúlò ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìbi ìṣeré ojútayé yìí tí kìí bá ti í ṣèèwọ̀.
- Àwọn eré òde òní ní í máa ṣàmúlò ibi ìṣeré àìjólójúkojú jù lọ.
- Ní àfikún, orí ìtàgé nínú oríṣìíríṣìí gbọ̀gàn ni àwọn eléré oníṣe onílànà Ogunde ti máa ń ṣeré olójúkojú wọn (b. a. gbọ̀ngàn ìlú, ti ilé ẹ̀kọ́, ilé ìtura, ilé àṣà ìbílẹ̀ ṣọ́ọ̀ṣì abbl.)

4. 1. 5 Aṣọ-eré

- Ẹ̀wù, tàbí irú aṣọ tí òṣèré/ aṣèsínjẹ wọ̀ tàbí tí ó ta mọ́ra ní àkókò ìṣeré wà lára èròjà pàtàkì tí ó ń mú kí ìsínnijẹ ṣe é ṣe.
- A máa ń mọ̀-ọ́n-mọ̀ gbé aṣọ eré kalẹ̀ lọ́nà tí yóò fi ṣàfihàn àwọn ohun tí ó ṣe kókó nípa ẹ̀dá-ìtàn tí aṣèsínjẹ ń sín jẹ.
- Àwọ̀ aṣọ a máa ṣe pàtàkì lọ́pọ̀ ìgbà. A le fi àwọ̀ ṣe ìdámọ̀ àwọn òrìṣà tí eré-oníṣe ọdún ìbílẹ̀ tí à ń ṣe jẹ mọ́. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, àwọ̀ funfun jẹ́ ìdánimọ̀ àwọn òrìṣà bí Ọbàtálá àti àwọn òrìṣà tó jẹ mọ́ omi bíi Ọ̀ṣún, Yemọja, Alárá-Igbó abbl. Bákan náà ni àwọ̀ pupa jẹ́ ìdánimọ̀ fún òrìṣà Ṣàngó nígbà tí à ń fi àmúlù àwọ̀ dúdú àti funfun/ pupa ṣe ìdámọ̀ Èṣù.
- Aṣọ-eré náà ni oríṣìíríṣìí ẹ̀kú/agọ̀ tí àwọn eléégún máa ń wọ̀ ni àsìkò ìṣeré eré-oníṣe ọdún ìbílẹ̀ àti oríṣirìṣi èyí tí àwọn eléégún aláré máa ń wọ̀ pidan. Lẹ́yìn tí wọn bá ti wọn ẹ̀kú tí wọ́n ń pè ní jẹ̀pẹ́ tàbí òkolonbo bí àwọ̀tẹ́lẹ̀ ní wọn máa ń wọ oríṣirìṣi aṣo eré mìíràn lé e lórí láti ṣe ìsínjẹ àwọn ẹ̀dá ìtà tí wọ́n bá fẹ́ sín jẹ. Bí àpẹẹrẹ, àwọn òṣèré eégún aláré máa ń ṣe àmúlò yẹ̀rì Ṣàngó láti fi pa idán orìṣà Ṣàngó, wọn a sì máa ṣe àmúlò ìró, bùbá àti gèlè láti fi pa idán ìyàwó.

- Nínú ìṣeré òde-òní (ti onílànà Ogunde tàbí ìṣere onítàn àpilẹ̀kọ lórí ìtàge tẹlifíṣàn, fídíò tàbí ìwé eré onífọ́tò) gbogbo àwọn ẹ̀wù àti aṣọ tí a máa ń wọ̀ lójú ayé náà ni wọ́n máa ń mú lò fún ìsínnijẹ àwọn ẹ̀dá ìtàn eré.

4. 1. 6 Ìbòjú àti àwọn ohun èlò ìṣeré mìíràn

- Ìbòjú lílò wọ́pọ̀ nínú ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ àti idán eégún aláré tí wọ́n jẹ́ eré-oníṣé àbáláyé ju nínú ìṣeré onílànà Ogunde àti àpilẹ̀kọ tí wọ́n jẹ́ eré-oníṣe òde òní lọ.
- Nínú àwọn ọdún ìbílẹ̀ bí ọdún Eégún, Gẹ̀lẹ̀dẹ́, Ọya, Ṣàngó, Orò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni a ti máa ń ṣe àmúlò ìbòjú.
- Àwọn ìbòjú yìí jẹ́ àwòrán orí ohun kan yálà ènìyàn, ẹranko, òrìṣà tàbí ẹ̀mí àìrí mìíràn.
- Bí a bá lo ìlànà ìmúlò àwọn ìbòjú náà oríṣi méjì tí a lè pín wọn sí ni aládàbojú àti aláṣíborí
- Bí a bá lo ìlànà ohun tí a fi ṣe àwọn ìbòjú náà ọ̀nà méjì mìíràn tí wọ́n pín síni aláṣọ àti onígi**.**
- Àwọn onígẹ̀lẹ̀dẹ́ àti eléégún, pàápàá eléégún aláré ní í máa lo oríṣiríṣi ìbòjú jù lọ.
- Àpẹẹrẹ ìbòjú ni àwọn ère orí ènìyàn lóríṣirísi pẹ̀lú ti oríṣirísi ẹranko àti àwọn ẹ̀dá àìrí mìíràn tí àwọn onígẹ̀lẹ̀dẹ́ àti eléégún máa ń ṣí borí [aláṣìíborí] tàbí tí wọ́n máa ń dà bojú [aládàbojú].
- Ìbòjú ni ó jẹ́ atọ́ka ẹ̀dá ìtàn tí àwọn eléégún aláré ń sín jẹ nínú idán tí wọ́n ń pa. Àpẹẹrẹ àwọn ìbòjú tí àwọn eléré eégún aláré máa ń lò ni ère orí òjòlá/erè, ère orí ọ̀nì, ere orí irò tàbí ti ọ̀bọ abbl.
- Àwọn ohun èlò ìṣeré mìíràn tí a máa ń ṣe àmúlò nínú eré-oníṣe lè jẹ́ ti ìléwọ̀ tàbí tí ibi ìṣeré/ orí ìtàgé. Ohun ẹ̀lò ìṣeré ìléwọ̀ ni àwọn tí òṣeré le mú dáni tàbí kí ó so mọ́wọ̀. Ti ibi ìṣeré/ orí ìtàgé ni àwọn ohun èlò ìṣeré tí a fi ń to ibi ìṣeré/ ìtàgé.

- Àpẹẹrẹ ohun èlò ìṣeré ìléwọ́ ni ìbọn, ọkọ́, ọ̀kọ̀, àdá, idà, ọ̀bẹ, ọgọ, àtòrì, ìrùkẹ̀rẹ̀, ṣẹ́ẹ́rẹ́, ààké, àṣẹ, ìkúnpá, òsùn, labà, ọ̀pá àṣẹ, ìgbàdí, àpamọ́wọ́, òrùka abbl. Àwọn òṣèré eré-oníṣe ọdún ìbílẹ̀ máa ń ṣe àmúlò àwọn nǹkan wọ̀nyí láti fi gbé ìsínjẹ ẹ̀dá ìtàn tí wọ́n ń sín jẹ nínú ìdàn tí wọ́ ń pa yọ.
- Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, kò sí bí àwòrò Ògún yóó ṣe ṣe ìsínjẹ òrìṣà Ògún tí kò níí mú ògbó/àdá/ idà/ ọ̀kọ̀ òrìṣà náà (tàbí ìbọn) lọ́wọ́ gẹ́gẹ́ bí ohun ìdámọ̀ pàtàkì òrìṣà náà. Bákan náà ni baba awo tó fẹ́ ṣe ìsínjẹ Ọ̀rúnmìlà gbọ́dọ̀ sọ àpò àgbìrà ifá kọ́, kí ó sì mú ìrọ́kin lọ́wọ́. Bí ọ̀rọ̀ ṣe rí nínú eré-oníṣe eégún aláré náà nìyí, òṣèré tí ó bá ń ṣe ìsínjẹ Ṣàngó máa ń mú oṣé/ṣẹ́ẹ́rẹ́ lọ́wọ́ láti fi sín Ṣàngó jẹ.
- Àpẹẹrẹ àwọn ohun èlò ìṣeré ibi ìṣere/ ìtàgé ni ìjókòó, ẹní, ibùsùn, ìyá odó, ìlù alágbékalẹ̀ bíi gbẹ̀du, ìgbìn àti àgbá, ọlọ, ìtẹ́ ọba, àwòrán ara ògiri, ère tàbí ohun àmì mìíràn tó dúró fún òrìṣà tí à ń ṣọdún rẹ̀ nínú eré ọdún ìbílẹ̀ abbl.

### 4. 1 . 7 Orin, Ìṣàré, Ìlù àti Ijó

- Orin kíkọ, ìṣàré ṣíṣe, ìlù lílù àti ijó jíjó jẹ́ àbùdá eré-oníṣe pàtàkì tí kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn, pàápàá jùlọ nínú eré-oníṣe àbáláyé. Àwọn èròjà mẹ́rin wọ̀nyí ní wọ́n máa ń dí àlàfo àìsí ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì tó bẹ́ẹ̀ ninú ìṣeré eré-oníṣe àbáláyé. Nípa lílo orin, ìbánisọ̀rọ̀ máa ń wáyé láàárín àwọn òṣèré eré-oníṣe àbáláyé.
- Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, àwọn eégún aláré máa ń lo orin, ẹ̀ṣà (tó jẹ́ oríṣìí ìṣàré kan) àti ìlù bàtá pẹ̀lú ijó rẹ̀ fún bíbá ara wọn sọ̀rọ̀ lójú agbo eré. ṣe àgbékalẹ̀ ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì nínú idán egúngún aláré.
- Nínú ìṣeré ọdún ìbílẹ̀, kì í sí ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì lọ títí rárá. Dípò àmúlò ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì, orin, ìlù, ìṣàré àti ijó ni wọ́n fi máa ń ṣe àgbékalẹ̀ ìbánisọ̀rọ̀ nínú ọdún ìbílẹ̀; yálà láàrin òṣèré síòṣèré tàbí láàrin àwọn òṣèré lápa kan sí òǹwòran lápakejì.
- Àmúlò àwọn èròjà mẹ́rẹ̀ẹ̀rin wọ̀nyí (ìlù, orin, ìṣàré àti ijó) a máa wáyé nínú ìṣeré òde òní náà. Àwọn eléré òde òní a máa lò wọ́n lóríṣiríṣi ọ̀nà fún ìméré dùn.

## 5.0 Ìsọníṣókí

- Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi tíátà tàbí ìṣeré.
- Àwọn àbùdá eré-oníṣe ajẹmọ́tíátà tí a jíròrò lé lórí ni ìsínjẹ/ ìsínnijẹ, aṣèsínjẹ, òǹwòran, ibi ìṣeré, aṣọ ìṣeré, ìbòjú àti àwọn ohun èlò ìṣeré mìíràn, orin kíkọ, ìṣàré ṣíṣe, ìlù lílù àti ijó jíjó.
- Ìsínjẹ/ìsínnijẹ ni a ṣàlàyé pé ó jẹ́ ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ fún gbogbo àwọn ìyókù.
- A ṣe àlàyé pé oríṣi òṣèré kan ni aṣèsínjẹ, a sì tọ́ka sí ìyàtọ̀ láàrin aṣèsínjẹ àti ẹ̀dá ìtàn.
- A ṣàlàyé rẹ̀ pé ìkópa àwọn òǹworan nínú ìṣeré a máa lọ́ọ̀rìn nínú ìṣeré àbáláyé ju ti òde òni lọ.
- A fi yé wa pé ibi ìṣeré olójúkojú, ní ojútáyé àti ní kọ̀lọ́fín tàbí ibi ìpamọ́ ni ìṣeré àbáláyé ti máa ń wáyé.
- Ibi ìṣeré olójúkojú àti aláìjólójúkojú ìṣeré òde òní ti máa ń wáyé. Ti olójúkojú a máa wáyé lórí ìtàgé nínú oríṣiríṣi gbọ̀ngàn. Ti àjólójúkojú lè wáyé lórí rédiò, tẹlifiṣàn, sinimá, fídíò, àwo rẹ́kọ́ọ̀dù tàbí ìwé eré onífọ́tò.
- A sọ pé àwọ̀ aṣọ eré jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú ohun tí a fi ń ṣe àgbé kalẹ̀ ẹ̀dáìtàn ní àkókò ìṣere.
- Ìbòjú aláṣìíborí, aládàbojú, onígi àti aláṣọ ni asọ pé ó wà àti pé ìlò wọn wọ́pọ̀ nínú ìṣeré àbáláyé ju tòde òní lọ. A sọ̀rọ̀ nípa ohun èlò ìṣeré ìléwọ́ àti ti ibi ìṣeré/ orí ìtàgé náà.
- A sọ wí pé ìlù lílù, orin kíkọ ìṣàré ṣíṣe àti ijó jíjó ni afi máa ń dí àlàfo àisí ìsọ̀rọ̀ngbèsì dàbí alárà nínú ìṣeré àbáláyé tí a sì máa ńlò bí èròjà améré dùn nínú ìṣeré òde òní.

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

i. Dárúkọ àwọn àbùdá eré-oníṣe ajẹmọ́ tíátà márùn-ún tí ó mọ̀?

ii. Kín ni ó mú ìsínjẹ ṣe pàtàkì ju àwọn àbùdá eré-oníṣe yòókù lọ?

iii. Kín ni ìyàtọ̀ láàrin ibi ìṣeré olójúkojú àti ibi ìṣeré aláìjójúkojú?

iv. Dárúkọ oríṣi ìbòjú mẹ́rin tí o mọ̀.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Adédèjì, J. A. 1978. "Alarinjo: The Traditional Yorùbá Travelling Theatre", Ogunba, O. àti Irele, A. (Olóòtú) *Theatre in Africa*. Ibadan University Press, o.i. 27-54. Ó tún wà nínú Ogunbiyi, Y. (olótùú) 1981, *Drama and Theatre in Nigeria: A Critical Source Book*, Nigeria Magazine Publication, Lagos, o.i. 221-247.

Ogundeji, P. A. 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. External Studies Programme, Department of Adult Education University of Ibadan, Ibadan, o.i. 126-128.

Ogundeji, P. A. 1992. *Yorùbá Drama 1(Eré-oníṣe Yorùbá 1*). Ibadan: Centre for External Studies University of Ibadan, Ibadan.

Ogundeji, P. A. 2000. *Ritual as Theatre, Theatre as Ritual: The Nigeria Example.* Ìṣẹ̀ṣe Monograph Series Atlantic Books, Ibadan and Ibadan Cultural Studies Group, University of Ibadan, Ibadan.

Ogundeji, P. A. 2014. *Yorùbá Drama in Time Perspective,* An Inaugural Lecture, 2013/14, Ibadan: Ibadan University Press.

# Ìpín 4: Àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀

Àkóónú

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròńgbà
3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Àbùdá Eré-oníṣe Yorùbá: Òde òní
5.0 Ìsọníṣóki
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáárà

A ti jíròrò lórí eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bí i tíátà nínú ìpín kẹta, a ṣe àlàyé àwọn àbùdá tí ó rọ̀ mọ́ ọn bíi ìsínjẹ, aṣèsínjẹ, òǹwòran, ibi ìṣeré, aṣọ eré, ìbòjú àti àwọn ohun èlò ìṣeré mìíràn pẹ̀lú ìṣàré, orin, ìlù àti ijó. Ní ìhín, a óò tẹ̀ síwájú láti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bí lítíréṣọ̀.

## 2. 0 Èròńgbà

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìwọ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ yóò ti lè:

- Dárukọ àwọn àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bí i lítíréṣọ.
- Tọ́ka sí àwọn àbùdá náà nínú eré-oníṣe.
- Ṣe àlàyé nípa àwọn àbùdá náà.
- Fi ìyàtọ̀ hàn dáradára láàárín àwọn àbùdá eré-oníṣe bí i tíátà àti bí i lítíréṣọ̀.

## 3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú

1. Lááríjà ni a tún lè pè ní _________.
2. Ní ṣọ́kí, kín ni àhupọ̀ ìtàn?
3. Dárúkọ àbùdá ìfìwàwẹ̀dá mẹta tí o mọ̀.
4. Kín ni ìyàtọ̀ láàárin ibùdó ìtàn àti ibi ìṣeré.

## 4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

- Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ nìkan ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ láti òkè òkun gbà sí lítíréṣọ̀, àwa gbàgbọ́ pé lítíréṣọ̀ alohùn náà wà, tí a tún lè pè ní àpilẹ̀ṣọ.
- Alohùn ni lítíréṣọ̀ àwọn Yorùbá àti ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ ẹ̀yà ilẹ̀ Áfíríkà ṣaájú kí wọ́n tó kó àṣà ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà dé.
- Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé ìṣe ni ó ṣe pàtàkì nínú eré-oníṣe, àpilẹ̀ṣe ni a ó máa pe àwọn eré tí wọ́n wà kí ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà tó dé dípò eré-oníṣe alohùn.
- Kíyèsí i wí pé kì í ṣe pé a kò lè sọ̀rọ̀ eré-oníṣe alohùn ni a kò ṣe ṣàmúlò rẹ̀, bí kò ṣe pé a fẹ́ tẹnpẹlẹ mọ́ ọ̀rọ̀ ìṣe tí eré náà jẹ mọ́ jù lọ; wọn a máa fọhùn nínú eré-oníṣe náà.
- Láti inú eré-oníṣe àbáláyé tí ó wà ṣaájú ìmọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà àti tòde òní tí ó bẹ̀rẹ̀ lẹ́yìn náà ni a óò ti máa mú àpẹẹrẹ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wa.

### 4. 1. 0 Àbùdá Eré-oníṣe bí i lítíréṣọ̀

- Àwọn àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bí i lítíréṣọ̀ tí a óò gbé yẹ̀ wò náà ni: kókó ọ̀rọ̀, ẹ̀dá ìtàn àti ìfìwàwẹ̀dá wọn, àhunpọ̀ ìtàn, ibùdó ìtàn, ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì àti ìlò èdè.
- Púpọ̀ àwọn àbùdá wọ̀nyí ni ó jẹ́ pé wọ́n fara hàn nínú àwọn ẹ̀yà lítíréṣọ̀ míràn bíi ewì àti ìtàn àròsọ náà.

4.1.1 Kókó ọ̀rọ̀

- Kókó ọ̀rọ̀ ni òye ọ̀rọ̀, gbòǹgbọ̀ ọ̀rọ̀ tàbí èrò tí iṣẹ́ lítíréṣọ̀ kan dá lé lórí. A tún lè pè é ní ẹ̀kọ́ tàbí ọ́gbọ́n tí a rí fa yọ ninú irú lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀. Gbogbo litíréṣọ̀ ní í máa ní kókó ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀; àti eré-oníṣe náà.
- Kókó ọ̀rọ̀ inú eré-oníṣe kan a máa sábà á ju ẹyọ kan ṣoṣo lọ. Èyí tí ó ṣe pàtàkì jù lọ ni olú kókó ọ̀rọ̀ tí gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ inú eré náà dá lé lórí látòkè délẹ̀. Àwọn mìíràn a máa pè é ní lááríjà.
- Àwọn kókó ọ̀rọ̀ kékèké, tí ó jẹ́ pé apá kan eré náà ni wọ́n ti sú yọ, tí wọn kò la gbo gbo rẹ̀ já látòkè délẹ̀ ni amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀.
- Àwọn amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ a máa ṣèrànwọ́ fún òǹworan/ òǹkàwé eré-oníṣe láti ní òye kíkún nípa olú kókó ọ̀rọ̀ ní ọ̀pọ̀ ìgbà; ìdí sì nìyí tí a fi pè wọ́n ní amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́.
- Ohun tí a lè pè ní olú kókó ọ̀rọ̀ inú ìṣeré àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá ni ọ̀rọ̀ àlàáfíà àwùjọ; kí ìlú tùbà kó tùṣẹ; kó dẹ tará ilé tará oko lọ́rùn. Èyí ni lááréjà tí ó la púpọ̀ nínú àwọn eré ìbílẹ̀ náà já.
- Lára àwọn ohun tí a lè pè ní amúgbálẹ́gbẹ̀ẹ́ kókó ọ̀rọ̀ ibẹ̀ ni ìfira-ẹni-jì, ìmọ́tótó, ṣíṣe ojúṣe ẹni, ìkansárá-sí ìwa akọni, ìwà ọmọlúwàbí bíbẹnu àtẹ́ lu ìwà àìdára, wíwárí fún aláṣẹ àti àwọn ajuní-lọ mìíràn abbl. Àpẹẹrẹ à máa jẹ yọ nínú Ọdún Edì ní Ilé Ifẹ̀, Ọdún Òrìṣà Adímú ní Èkó, Ọdún Ògún àti Ọdún Ọba ní Oǹdó abbl.
- Àwọn eré kékèké ni àwọn eléégún aláré máa ń ṣe. Wọn a sì máa ṣe àmúlò ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀ pupọ̀púpọ̀. Àwọn kókó ọ̀rọ̀ bí i ọ̀rọ̀ ìwà ọmọlúwàbí, ẹwà, ìbọlá fún àwọn òrìṣà, ìṣe àti àṣà Yorùbá, ìkọlura àṣà àbáláyé àti ti òde òní, àwọn àjèjì láàrín Yorùbá abbl.
- Nínú eré odé òní onílànà Ogunde àti ti àpilẹ̀kọ àwọn èré tí ó ń ṣe àmúlò ìtàn ìwáṣẹ̀ àti ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi tí ó ń fi kókó ọ̀rọ̀ nípa ìṣe akọni àti ọ̀rọ̀ ìṣèlú ìbílẹ̀ àbáláyé Yorùbá hàn wà. Àpẹẹrẹ ni *Ọba Kòso, Mọrèmí,* látọwọ́ Dúró Ladipọ; Aláàfin Aganjú látọwọ́ Ìṣọ̀lá Ògúnṣọlá; *Baṣọ̀run Gáà,* látọwọ́ Adébáyọ̀ Fálétí; *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* látọwọ́

Akínwùmí Ìṣọ̀lá àti *Líṣàbi Agbòǹgbò Àkàlà* látọwọ́ Olú Owólabí. Àwọn eré-oníṣeòde òní tí ń fi kókó ọ̀rọ̀ nípa ìwà ọmọlúwàbí láwùjọ hàn wà, bẹ́ẹ̀ ni àwọn tí ń fi ọ̀rọ̀ ìṣèlú òde ònín, ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn àtìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ mìíràn láwùjọ hàn náà wà. Irú ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ ti abẹ́lé lẹ́ẹ̀dẹ̀, ibi iṣẹ́, ilé ẹ̀kọ́ abbl. [Àpẹẹrẹ wà nínú àwọn eré bíi *Àṣírí Bàbá Ìbejì* látọwọ́ Akin Ògúngbè, *Èkùrọ́ Olọ́jà* àti *Orogún Adédigba* látọwọ́ Oyin Adéjọbí, *Ìfẹ́ Owo* látọwọ́ Kọlá Ògúnmọ́lá *Yòrùbá Ronú* àti *Kẹ̀yìn Sókun* láti ọwọ́ Hubert Ogunde; *Àgbàlọ́wọ́mérìí Baálẹ̀ Jòǹtolo* latọwọ́ J. F. Ọdúnjọ, *Àbíkú Solóògùn Dèké*, *Àgbà tí ń Yọ́lè Dà* àti *Oyíndàmọ́lá Ọmọ Ọlọ́rọ̀*, látọwọ́ Olú Owólabí, *Alàgbà Jeremáyà* látọwọ́ Oyètúndé Awóyẹlé, *Abẹ́ Ààbò*, látọwọ́ Akínwùmí Ìṣọ̀lá àti *O Ṣèyí tán* látọwọ́ Yẹmisí Adébọ̀wálé.

1. 4. 2 Ẹ̀dá ìtàn àti ìfìwàwẹ̀dá

- Àwọn ènìyàn àti ẹ̀dá mìíràn tí wọ́n wà nínú àhunpọ̀-ìtàn eré-onítàn tàbí ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ ìsínjẹ inú ìṣeré àdáyébá ni ẹ̀dá-ìtàn (ẹ̀dá tí ó wà nínú ìtàn > ẹ̀dá inú ìtàn > ẹ̀dá ìtàn). Àwọn ẹ̀dá ìtàn wọ̀n-ọn-nì kì í ṣe ènìyàn gidi lójú ayé. Nínú àwọn eré-oníṣe àbáláyé ti ọdún ìbílẹ̀ àti eégún aláré wọn lè jẹ́ òrìṣà, baba ńlá tàbí ìyá ńla tí ó wà nínú ìtàn ìwáṣẹ̀ tàbí ti akọni-kàyéfì tí ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ dá lé tàbí ẹ̀mí àìrí kan tí ìṣeré náà jẹ mọ́.
- Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe àlàyé nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kẹta, àwọn ẹ̀dá ìtàn wọ́nyí ni àwọn aṣẹ̀sínjẹ ń sín jẹ ní àkókò ìṣeré.
- Ní àkókò ọdún eégún káàkiri ilẹ̀ Yorùbá Baba-ńlá kan tàbí òmíràn ni ẹ̀dá ìtàn tí arẹ̀kú egúngún máa ń sínjẹ. Arẹ̀kú ni aṣesínjẹ. Nígbà tí ẹlẹ́gùn Ṣàngó bá ń ṣeré ní ojú agbo eré Ṣàngó gangan-an ni ẹ̀dá ìtàn tí ó ń sín jẹ, ẹlẹ́gùn ni aṣèsínjẹ.
- Nínú ìṣeré eégún aláré àwọn eégún apidán ni a óò rí bí aṣesínjẹ tí àwọn ẹ̀dá ìtàn tí wón ń yí padà sí bí i ẹkùn, òjòlá, ọ̀bọ, òyìnbó, Tápà, ọ̀mùtí, ọ̀falè abbl. yóò sì jẹ́ ẹ̀dá ìtàn.
- Nínú ìṣeré òde òní onílànà Ogunde, ẹ̀dá ìtàn ni Ọba Fìwàjoyè tí ó jẹ́ olú ẹ̀dá ìtàn nínú eré-oníṣe *Yorùbá Ronú*. Bákan náà ni ó jẹ́ pé ẹ̀dá ìtàn ni Bàbá Sàlá nínú eré sinnimá *Ọ̀run Móoru*, Moses Ọláìyá sì ni aṣèsínjẹ tí ó ṣèsíjẹ rẹ̀ nínú sínnimá náà.

- Lára àwọn ẹ̀dá ìtàn pàtàkì inú eré àpilẹ̀kọ *Baṣọ̀run Gáà*, ni Baṣọ̀run]/, jxet Gáà, Aláàfin Abíọ̀dún Adégoólú, Àgbọ̀nyín, àti Akínkúnmi tí David Ọ̀jẹ́dòkun, Túbọ̀sún Ọdúnsì, Adéwùmí Fálétí, àti Lárìndé Akinlẹ̀yẹ ti ṣe ìsínjẹ wọn nínú ìṣeré náà sóri fọ́n-ọ́n-rán tàbí Sí Diì fídíò àgbéléwò.
- Ìṣèsínjẹ ẹ̀dá ìtàn a máa wáyé nígbà tí aṣèsínjẹ bá lo oríṣiríṣi ọgbọ́n ìṣeré láti ṣe ìmúlò àwọn àbùdá ìṣeré tàbí tíátà tí a tí mẹnu bà nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kẹta fún ṣíṣe ìgbékalẹ̀ ẹ̀dá ìtàn gẹ́lẹ́ bí ó ti wà nínú ìtàn eré.
- Ní àkókò ìṣẹ̀dá eré òde òní onílànà Ogunde àti ti àpilẹ̀kọ olùṣẹ̀dá eré a máa ní ìsínjẹ lọ́kàn bí wọ́n ṣe ń ṣe ìgbékalẹ̀ àwọn ẹ̀dá ìtàn wọn.
- Gbogbo ọgbọ́n ìṣàgbékalẹ̀ àwọn ẹ̀dá ìtàn wọ̀nyí lọ́nà tí wọn ó fi ní àfijọ ènìyàn tàbí ẹ̀dá tí wọ́n ní lọ́kàn ni à ń pè ní ìfiwàwẹ̀dá.
- Ọ̀nà mẹ́rin tí Ògúndèjì (1992) pín ọgbọ́n ìfiwàwẹ̀dá tí àwọn olùṣẹ̀dá eré máa ń mú lò sí ni fífún wọn ní orúkọ pẹ̀lú ṣíṣe ìgbékalẹ̀ ìrísí, ìṣesí àti ìhùwàsí wọn.
- Orúkọ **:-** Ohun ìdámọ̀ pàtàkì ni orúkọ jẹ́ fún ẹ̀dá ìtàn. Lọ́pọ̀ ìgbà ni ó jẹ́ pé orúkọ tí a fún ẹ̀dá ìtàn kan máa ń jẹ́ atọ́ka sí àwọn àbùdá ìfiwàwẹ̀dá rẹ̀ yòókù; orúkọ rẹ̀ yóó máa rò ó, yóó máa nípa lórí rẹ̀; ṣé orúkọ kúkú máa ń roni, oríkì a sì máa rònìyàn bẹ́ẹ̀ sì ni orúkọ ìsọmọ ni àwọn Yorùbá gbà pé ó máa ń ro ọmọ. Gbogbo orúkọ tí à ń jẹ́ lójú ayé náà ni olùṣẹ̀dá eré-onítàn lè mú lò.
- Ìrísí **:–** Nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìrísí ẹ̀dá ìtàn, a ó máa sọ̀rọ̀ bí ẹ̀dá ìtàn náà ti ga tàbí bí ó ti kúrú sí; bí ó ti lára sí, bóyá ó ní àmì ara kan tàbí òmíràn bí irun orí rẹ̀ ti rí; ìmúra tàbí ìwọsọ ẹni náà pẹ̀lú gbogbo àwọn ohun tí ó bá ta mọ́rá.
- Àfojúrí ni gbogbo àwọn ohun wọ̀nyí máa ń jẹ́ nínú ìṣeré. Ṣùgbón bí ó bá jẹ́ eré àpilẹ̀kọ, láti inú àwọn àlàyé ìtọ́nisọ́nà tí òǹkọ̀wé eré-onítàn bá kọ, àti ọ̀rọ̀ ẹnú ẹ̀dá ìtàn náà pẹ̀lú ohun tí àwọn ẹ̀dá ìtàn míràn bá sọ nípa rẹ̀ ni a ó ti máa ṣe àfàyọ òye nípa ìrísí àti àwọn àbùdá ọnà ìfiwàwẹ̀dá mìíràn.
- Ìṣesí **:–** Èyí ni ìṣe tó ti di bárakú fún ènìyàn, ṣúgbọ́n tì kì í ṣe ohun tó le pa ẹlòmíràn lára lọ́pọ̀ ìgbà. Lọ́pọ̀ ìgbà ni ó jẹ́ pé olùṣẹ̀dá eré-onise máa ń mọ̀-ọ́n-mọ̀ lo ìrísí fún ìdámọ̀ ẹ̀dá ìtàn ni. Àpẹẹrẹ ni fífi ọwọ́ pa túbọ̀mú ní gbogbo ìgbà, dídẹ̀gbẹ́ rìn, wíwọ́sẹ̀

nílẹ̀ rìn tàbí fífí bàtà kilẹ̀ kà kà kò kò; ọ̀ lè jẹ́ rírànmú sọ̀rọ̀ tàbí oríṣi ìpèdè kán tí ó ti mọ́ ẹ̀dáìtàn náà lẹ́nu, bí àpẹẹrẹ, "Ẹ máa gbádùn, ẹ máa yọ̀tọ̀mì", "Ire ni o!" abbl.

- Ìhùwàsí **:–** Èyí ni àwọn ìgbésẹ̀ tí ẹ̀dá ìtàn kan gbé tàbí ìṣe rẹ̀ tí ó máa ń nípa kan tàbí òmíràn lórí àwọn ẹ̀dá ìtàn míràn. Irú àwọn ìhùwàsí/ ìwà bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ rere tàbí búburú. Èyí dúró lórí irú ipa tí ìṣe tàbí ìgbésẹ̀ ẹ̀dá ìtàn tí à ń gbé yẹ̀ wò náà bá ní lórí àwọn ẹ̀dá ìtàn mìíràn. Bí ó bá ní ipa rere, a jẹ́ pé ìwà rere ni, bí ó bá sì ní ipa búburú a jẹ́ pé ìwà búburú ni. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, ìlànà àwùjọ, ti ẹgbẹ́/ àjọ tàbí ti ẹ̀sìn ni a fi máa ń ṣe òdìwọ̀n ìwà, bóya dáradára ni tàbí burúkú. Bí èyí tilẹ̀ rí bẹ́ẹ̀, síbẹ̀síbẹ̀ ipa tí ìwà kó lórí ọmọlàkejì ṣe pàtàkì.
- Àpẹẹrẹ ìhùwàsí tàbí ìwà rere: òtítọ́, àànú, ìṣoore, sùúrù, ọ̀yàyà, ìkónimọ́ra, àìṣèmẹ́lẹ́, ìfira-ẹni-jì, ìrẹ̀lẹ̀, ìfẹ́ abbl.
- Àpẹẹrẹ ìwà búburú tàbí àìdára: ẹ̀tàn/ ilẹ̀ dídà/ àìṣòótọ́, arankan, ìdìtẹ̀, irọ́ pípa/ èké ṣíṣe, ìbínú/ inúfùfù, ìgbéraga, ìkóríìra, ahun ṣíṣe, olè jíjà abbl.
- Gbogbo àwọn ọgbọ́n ìfìwàwẹ̀dá wọ̀nyí ni àwọn òǹkọ̀wé eré-onítàn máa ń mú lò láti dáṣọ ìwà wọ àwọn ẹ̀dá ìtàn wọn kí àgbékalẹ̀ eré náà le sún mọ́ ojú ayé.

## 4. 1. 3 Àhunpọ̀ ìtàn

- Ètò ìṣẹ̀lẹ̀ inú eré, bí olùṣẹ̀dá eré/ òǹkọ̀wé eré-onítàǹ bá ṣe tò ó láti ìbẹ̀rẹ̀ títí dé ìparí ní ṣíṣẹ̀ntẹ̀lé ni àhunpọ̀-ìtàn.
- Ó wà lára àbùdá tí a gbà pé ó ṣe pàtàkì nínú eré-oníṣe òde òní (ti onílànà Ogunde àti tàpilẹ̀kọ) tí í máa sábà ní àhunpọ̀ ìtàn tí ó lọ tààrà dáadáa ní ìbámu pẹ̀lú èrò àwọn onímọ̀ òkè òkun àti ọ̀làjú tí wọ́n kó wá sí ọ̀dọ̀ wa.
- Nínú àwọn eré-oníṣe àbáláyé (ti ọdún ìbílẹ̀ àti teégún aláré) àhunpọ̀ ìtàn tí ó lọ tààrà kò wọ́ pọ̀, lábalalábala ni ó máa ń sábà jẹ́.
- Ìlò àmì nípa ijó, ìmúra, ìbòjú, ìrìnsókèsódò àti àwọn ọnà ìsínnijẹ mìíràn ni a fi ń gbé e kalẹ̀, ó sì máa ń mọ níba. Èyí ni kì í jẹ́ kí àhunpọ̀-ìtàn tí ó wà nínú àwọn ìṣeré náà hàn gbangba, tí àwọn onímọ̀ kan sì fi rò pé wọn kò ní àhunpọ̀-ìtàn rárá.
- Ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó jẹ́ pé nípa ìṣèwádìí àti ìtọpinpin ni a fi máa ń ní òye kíkún nípa àhunpọ̀ ìtàn tí wọ́n ń fi àwọn àmì inú wọn paròkò.

- Àhunpọ̀ ìtàn nínú àwọn eré òde òní a máa gùn ju ti tàbáláýé lọ dáradára, wọn a sì máa sábà lọ tààrà bí ṣe sọ.
- A lè pín ètò àhunpọ̀ ìtàn inú àwọn eré òde òní sí mẹ́ta: ìbẹ̀rẹ̀, àárín àti ìparí.
- Ìbẹ̀rẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn ni olùṣẹ̀dá eré ti í ṣàgbékalẹ̀ ìṣòro (èdè, àìyedè, ọ̀rọ̀ tó rúni lójú, ìtakora kan tàbí òmíràn), àárin ni ìṣoro náà ti máa ń díjú sí i nípasẹ̀ ìkọlura àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn. Ìparí àhunpọ̀ ìtàn ni ibi àgbálọgbábọ̀ tàbí ìgúlẹ̀, tí ìṣoro inú àhunpọ̀ ìtàn ti máa ń ní ìyanjú tàbí ojútùú.
- Oríṣìíríṣìí ọgbọ́n tàbí àbùdá ìhùntànpọ̀ ni àwọn olùṣèdá eré-onítàn máa ń mú lò láti mú kí ìṣòro inú àhunpọ̀-ìtàn máa díjú sí i bí àhunpọ̀ ìtàn ṣe ń tẹ̀ síwájú, kí àwọn òǹwòran wọn sì máa gbádùn rẹ̀ dé góńgó. Bí àpẹẹrẹ: ìkóni-láyà-sókè, ìṣẹ̀lẹ̀ ẹ̀yìn ìtàgé, ìṣẹ̀lẹ̀ àyàbá, ìjọnílójú, ẹ̀dà-ọ̀rọ̀ ajẹméré oníṣe abbl.
- Àárín àhunpọ̀-ìtàn ni ibi òtéńté máá ń wà; níbi tí ìkọlura tàbí ìṣoro inú àhunpọ̀ ìtàn ti dé ojú àmì tàbí ibí tí ó ga jù lọ. Ibi gbèdéke yìí ni yóó sì ti máa súré tete lọ sí ibi ìparí.

## 4. 1. 4 Ibùdó ìtàn

- Ibùdó ìtàn ni àwọn ibi/ àyè, tí ó wà nínú ìtàn eré-oníṣe tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn ti ṣẹlẹ̀. Kíyèsí i pé wọn kì í ṣe àyè tàbí ibìkan pàtó ní ojú ayé ní àkókò bágbàmu.
- Ní àkókò ìṣeré, ibi ìṣeré, (b. a. ojú agbo eré/ orí ìtàgé) ni a ti máa ń ṣe ìgbékalẹ̀ tàbí ìfihàn ibùdó ìtàn.
- Ọ̀nà méjì ni a lè pín ibùdó ìtàn sí: ti gbogbogbòò; ti ibi pàtó.
- Ibùdó ìtàn gbogbogbòò ni ibùdó ìtàn nńlá tí ó kó àwọn ìbùdó ìtàn kékèké bọnú. Ibùdó ìtàn pàtó ni àwọn ibùdó ìtàn kékèké tí ibùdó ìtàn nńlá kó bọnú. Àwọn ìlú/ àwùjọ tí ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìtàn ti ṣẹ̀lẹ̀ ni ibùdó ìtàn gbogbogbòò já sí, nígbà tí ibùdó ìtàn pàtó jẹ́ àwọn ibi pató tí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ti wáyé nínú ìlú tàbí àwùjọ inú ìtàn.

## 4. 1. 5 Ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì (Ìlò èdè)

- Ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì ni bátànì bí àwọn ẹ̀dá-ìtàn inú eré-oníṣe ṣe ń gba ọ̀rọ̀ ní ẹnu ara wọn.

- Ọ̀kan pàtàkì lára àwọn àbùdá tí a gbà pé ó pọn dandan nínú eré-oníṣe ni, pààpàá jùlọ àwọn eré-oníṣe òde òní (ti onílànà Ogunde àti tàpilẹ̀kọ), ṣùgbọ́n kò wọ́ pọ̀ nínú eré-oníṣe àbáláyé.
- Níbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ eré-oníṣe onílànà Ogunde, nípasẹ̀ ìwọ́hùn orin kíkọ ni àwọn òṣèrè fi máa ń ṣe ìgbékalẹ̀ ìsọ̀rsọ̀ǹgbèsì, ṣùgbọ́n lẹ́yìnọ̀rẹyìn, ìlànà ìwọ́hùn ìsọ̀rọ̀ ojoojúmọ́ ni wọ́n fi ń gbé e kalẹ̀. Èyí kò sọ pé wọn kì í ṣe àmúlò ìwọ́hùn orin tàbí ti ìpohùn ewì míràn ní ibi tó bá yẹ.
- Ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì kò wọ́ pọ̀ nínú ìṣeré àbáláyé (ọdún ìbílẹ̀ àti eégún aláré); ìṣàré, orin, ohùn ìlù, ijó àti ìlò àmì ní í máa ṣe iṣẹ́ ìbánisọrọ̀ tí ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì nínú wọn.
- Ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì ni ó máa ń fààyè sílẹ̀ fún ìbáni-sọ̀rọ̀ láàrin àwọn ẹ̀dá ìtàn inú eré. Láti inú àwọn ìbánisọrọ̀ yìí ni awa bí òǹkawé tàbí òǹwòran eré-oníṣe yóò ti máa ṣe àfàyọ àtòjọ ìṣẹ̀lẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn àti irú ènìyàn tí ẹ̀dá ìtàn kọ̀ọ̀kan jẹ́ nínú àhunpọ̀ ìtàn eré).
- Ó hàn gbangba-gbàǹgbà wàyí pé nípasẹ̀ ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì àárín àwọn ẹ̀dá ìtàn náà ni ìbánisọ̀rọ̀ láàrin olùṣẹ̀dá eré àti òǹkàwé/ òǹwòran eré tí í maá wáyé.
- Bí ìbánisọ̀rọ̀ àárín àwọn ẹ̀dá ìtàn bá jẹ́ ìbánisọ̀rọ̀ lọ́nà tààrà, ti àárín olùṣẹ̀dá eré àti àwọn ònkàwé/ òǹwòran rẹ̀ yóò jẹ́ ìbánisọ̀rọ̀ lọ́nà ẹ̀rọ.
- Kò sí àní àní wí pé láti inú ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì ni a ti máa ń rí oríṣiríṣi ìlò èdè; yálà ti ọnà èdè ( àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, àfiwé tààrà, ìfohunpènìyàn, àfidípò abbl.) àti ọnà ìṣọwọ́lò-èdè (b. a. àwítúnwí, ìfohùn dárà, abbl.) pẹ̀lú àwọn èròjà ọnà alohùn àbáláyé (b. a. òwe, oríkì, ọfọ̀, ẹsẹ ifá orin àlọ́ onítàn abbl.).
- Ìyàtọ̀ gbòógì tí í máa wà láàrin ìlò èdè nínú eré-oníṣe àti ewì ni pé a kì í sábàá láǹfàní láti ní òye kíkún nípa ọ̀gangan ipò ìmúlò èdè nínú ewì, níṣe ni a óò máa ṣe àfayọ rẹ̀ láti inú àgbékalẹ̀ akéwì; ṣùgbọ́n òye kíkún a máa sábà wà nípa ọ̀gangan ipò àmúlò èdè nínú eré-oníṣe.

## 5. 0 Ìsọníṣókí

- A ti ṣe àlàyé àwọn àbùdá àjẹmọ́-lítíréṣọ̀ bí ó ṣe hàn nínú eré-oníṣe àbáláyé àti tòde òní nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Àwọn àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bí i lítíréṣọ̀ tí a jíròrò lé lórí náà ni: Kókó ọ̀rọ̀, ẹ̀dá ìtàn àti ìfìwàwẹ̀dá wọn, àhunpọ̀ ìtàn, ibùdó ìtàn, ìsọ̀rọ̀ngbèsì àtilò èdè.

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Dárúkọ àwọn àbùdá eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀ márùn-ún.
2. Kín ni ìyàtọ̀ láàárín òṣèré àti ẹ̀dá ìtàn?
3. Kín ni ìyàtọ̀ tó wà láàárín ibi ìṣeré àti ibùdó ìtàn?
4. Kín ni ìyàtọ̀ àárín ìlò èdè nínú ewì àti eré-oníṣe?

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Clark, E. 1979. *Hubert Ogunde: The Making of Nigerian Theatre.* Oxford: Oxford University Press.

Ogundeji, P. A. 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature.* External Studies Programme, Department of Adult Education University of Ibadan, Ibadan, o.i. 126-128.

Ogundeji, P. A. 1992. *Introduction to Yorùbá Written Literature* External Studies Programme, Department of Adult Education University of Ibadan, Ibadan,

Ogundeji, P. A. 2001. "Eré-oníṣe Yorùbá" nínú Bádé Àjàyí, (olóòtú) *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Ẹ̀dá-èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà Yorùbá*: *Ẹ̀dá-èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*, Ẹka Ìmọ̀ Ẹ̀dá-Èdè àti Èdè Afíríkà Yunifásítì Ìlọrin, Ìlọrin. o. i. 167-188.

# MÓDÙ II:

# ERÉ-ONÍṢE ÀBÁLÁYÉ

## Ìpín 1: Ǹjẹ́ eré-oníṣe ni òdún ìbílẹ̀?

Àkóónú

1. 0 Ìfáárà
2. 0 Èròǹgbà
3. 0 Ìbéèrè ìṣáájú
4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4. 1 "Ọdún ìbílẹ̀ kì í ṣe eré oníṣe"
4. 2 "Eré oníṣe ni ọdún ìbílẹ̀"
4. 3 "Àwọn ọdún ìbílẹ̀ kan jẹ́ eré-oníṣe, àwọn kan kì í ṣe eré-oníṣe"
5. 0 Ìsọníṣókí
6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7. 0 Ìwé ìtọ́kasí

### 1. 0 Ìfáárà

Ó ṣe pàtàkì láti mẹ́nu bà á ní ìbẹ̀rẹ̀ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí wí pé láti inú àwọn ìsínjẹ tí ó jẹ mọ́ àwọn orò inú ọdún ìbílẹ̀ ni tíátà káàkiri àgbáyé ti dìdelẹ̀ àti pé kò sí àríyànjiyàn lááárín àwọn onímọ̀ eré káàkiri àgbáyé nípa eléyìí. Àpẹẹrẹ irúfẹ́ àwọn orò ṣíṣe báwọ̀nyí wọ́ pọ̀ nínú àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá. Bí ẹnu ṣe kò nípa orísun tíátà yìí, ẹnu kò kò bẹ́ẹ̀ lórí bóyá ó tọ̀nà láti ka àwọn ọdún ìbílẹ̀ ní ilẹ̀ Áfíríkà (àti ilẹ̀ Yorùbá náà) sí eré-oníṣe tàbí kò yẹ. Láti dáhùn ìbéèrè tí ó wà ní àkọlé ìpín kìn-ín-ní yìí a ó ṣe àgbéyẹ̀wò èrò àwọn onímọ̀ lórí àríyànjiyàn náà: bóyá ó tọ̀nà tàbí kò tọ̀nà láti pe àwọn ìṣeré orò inú ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ Afíríkà (èyí tí Yorùbá jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára wọn) ní eré-oníṣe. Ọ̀nà méjì gbígbòòrò tí èrò àwọn onímọ̀ pin sí nípa àríyànjiyàn yìí, tí a ó sì jíròrò lé lórí nínú ìpín yìí ni ti àwọn tí ó sọ pé "Ọdún ìbílẹ̀ kì í ṣe eré-oníṣe" àti ti àwọn tí wọ́n ta kò wọ́n, tí wọ́n wí pé "Eré-oníṣe ni ọdún ìbílẹ̀". Ẹ̀wẹ̀, a rí onímọ̀ kan tó jẹ́ aṣọ̀túnṣòsì lááárín àwọn èrò méjèèjì yìí. Ó gbà pé "Àwọn orò ọdún ìbílẹ̀ kan jẹ́ eré-oníṣe, àwọn kan kì í ṣe eré-oníṣe". Nítorí èrò kẹta yìí ṣe ìmúlò èrò méjèèjì ti àkọ́kọ́, a lè má fẹ̀ẹ́ rí i gẹ́gẹ́ bí èyí tí ó ṣe pàtàkì, ṣùgbọ́n nítorí ìdí tí ì báà wúlò fún, a óò gbé e yẹ̀ wò bí èrò kẹta nípa àríyànjìyàn náà.

### 2. 0 Èròǹgbà

Ní òpin ìdílẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó ti lè:

- Sọ iye ìsọ̀rí tí èrò àwọn onímọ̀ pin sí lórí àríyànjiyàn nípa bóyá eré-oníṣe ni àwọn ọdún ìbílẹ̀ tàbí wọn kì í ṣe eré-oníṣe.

- Dárúkọ àwọn onímọ̀ tí ó wà ní ìsọ̀rí èrò kọ̀ọ̀kan tí àríyànjiyàn náà pín sí.
- Ṣe ìdámọ̀ àtí àlàyé nípa èrò àwọn ìsọ̀rí onímọ̀ náà lọ́kọ̀ọ̀kan.
- Sọ èrò tí o fara mọ́ jùlọ, àti ìdí tí o fi fara mọ́ ọn.

## 3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú

1. Ìsọ̀rí mélòó ni èrò àwọn onímọ̀ pín sí lórí bóyá eré-oníṣe ni ọdún ìbílẹ̀ tàbí kì í ṣe eré oníṣe?
2. Ṣe ìdámọ̀ àwọn ìsọ̀rí náà.
3. Dárúkọ àwọn onímọ̀ tí ó léwájú èrò ìsọ̀rí onímọ̀ kọ̀ọ̀kan.

## 4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4. 1 "Ọdún ìbílẹ̀ kì í ṣe eré oníṣe"

- Lára àwọn onímọ̀ tí kò gbà pé ọdún ìbílẹ̀ Áfíríkà jẹ́ eré-oníṣe ni Molly Mahood (1966), Ulli Beier (1967), Ruth Finnegan (1970), Michael Echeruo (1973) àti J. C. de Graft (1976).
- Àwíjàre wọn ni pé àwọn ọdún ìbílẹ̀ náà kàn ṣe ìmúlò àwọn àbùdá tàbí fọ́nrán eré oníṣe lásán ni, wọn kì í ṣe eré-oníṣe gan-an. Orò tí ó jẹ mọ́ ẹ̀sìn ni wọ́n kà wọ́n sí. Nítorí náà wọn ṣe àpèjúwe àwọn ọdún ìbílẹ̀ náà gẹ́gẹ́ bíi "ọlẹ̀ eré-oníṣe", (*embryonic drama*) tàbí "kògbókògbó eré-oníṣe", tí "kò múná dóko" tàbí tí "kò ì dàgbà tó" (*pre-drama*).
- Bí Ògúndèjì (2014) ṣe tọ́ka sí i, lórí ìrírí àwọn òyìnbó ará Yúróòpù ni èrò àwọn onímọ̀ yìí gùn lé níbi tí ó ti jẹ́ pé ìdárayá/ ìgbádùn ẹwà iṣẹ́ ọnà ni ohun bàbàrà jù lọ sí wọn.
- Nípasẹ̀ ṣíṣe àfiwé àwọn ọdún ìbílẹ̀ Afíríkà kan pẹ̀lú ti ilẹ̀ Sumeria àti Ilẹ̀ Gíríkì, Echeruo tọ́ka sí i pé ọdún ìbílẹ̀ Áfíríkà kò fara jọ ti ilẹ̀ fara jọ ti Gíríkì tí wọ́n gbà gẹ́gẹ́ bí ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ eré-oníṣe ni Yuróòpù, pé ti ilẹ̀ Sumeria tí eré-oníṣe kò ti sú yọ gedegbe ni wọ́n jọ jùlọ. Ó pe àkíyèsí sí i pé àṣeyẹ ọdún ìbílẹ̀ Sumeria náà àti àwòmọ́ eré-oníṣe ibẹ̀ kò ṣe é yà sọ́tọ̀ọ̀tọ̀ tàbí kí wọ́n dá dúró; wọ́n wọnú ara típẹ́típẹ́. Ó ní èyí kò rí bẹ́ẹ̀ nínú ọdún Daonisu ní ilẹ̀ Gíríkì níbi tí ó jẹ́ pé ìṣeré oníṣe dá dúró gẹ́gẹ́ bí ayẹyẹ ìdíje fún ìdárayá àti ìgbádùn àwọn òǹwòran. Kò wọnú ayẹyẹ ọdún òrìṣà Daonisù típẹ́típẹ́.

- Àìsí àhunpọ̀ ìtàn tààrà tún jẹ́ ohun pàtàkì tí Echeruo fi sọ pé ọdún ilẹ̀ Sumeria kì í ṣe eré oníṣe. Gẹ́gẹ́ bí èrò Echeruo ètò, ìṣẹ̀lẹ̀ inú irú ọdún ìbílẹ̀ yìí kì í ṣe ti aláhunpọ̀-ìtàn eré-oníṣe bí kò ṣe èyí tí ó wà láti fi ṣe ẹ̀yẹ àjọ̀dún òrìṣà.
- Ulli Beier tilẹ̀ sọ ní tirẹ̀ pé àwọn ọlọ́dún ìbílẹ̀ bẹ́ẹ̀ kì í rí ara wọn bí eléré, bí kò ṣe bí i ẹlẹ́sìn: àríyá ajẹmẹ́sìn ni ó sọ pé wọ́n gbà pé àwọn ń ṣe ní àkókò ọdún ìbílẹ̀.

## 4. 2 "Eré-oníṣe ni ọdún ìbílẹ̀"

- Lára àwọn onímọ̀ tí ó fara mọ́ ọn wí pé kí á gba ọdún ìbílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí irúfẹ́ eré-oníṣe kan ní ilẹ̀ Áfíríkà, ni Ogunba (1978), Adedeji (1972), Ugonna (1983), Enekwe (1987) àti Ògúndèjì (1992, 2000, 2005, 2012, 2014), Ibitokun (1993).
- Àwọn wọ̀nyí gbà pé ìsínnijẹ tí ó wà nínú àwọn ọdún ìbílẹ̀ náà ni ó ṣe pàtàkì jùlọ. Wọ́n gbà pé níwọ̀n ìgbà tí ìṣèsínjẹ ti fara hàn nínú àwọn ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ náà, a lè pè wọ́n ní oríṣi eré-oníṣe kan láàyè ara wọn.
- Wọ́n rí àwọn bíi abọrẹ̀, ẹlẹ́gùn, ọba àtìjòyè pẹ̀lú arugbá gẹ́gẹ́ bí aṣèsínjẹ ní àkókò ìṣeré. Àwọn wọ̀nyí ni wọ́n kà sí aṣèsínjẹ́ òrìṣà, ẹ̀mí àìrí, akọni ayé àtijọ́ kan tàbí òmíràn nínú ìtàn ìwáṣẹ̀ tàbí takọni-kàyéfì tí ó wà lẹ́yìn àwọn ọdún ìbílẹ̀ náà.Ìlò àwọn àbùdá ọnà ìṣèsínjẹ bíi aṣọ eré, ijó, ìlù, ìbòjú abbl. ni wọ́n gbà pé wọ́n fi máa ń ṣe ìsínjẹ náà.
- Àwon onímọ̀ yìí gbà pé lábalalábala ni àhunpọ̀-ìtàn inú àwọn eré ọdún ìbílẹ̀ náà àti pé ìlò àmì ní a fi ṣe ìgbékalẹ̀ àhùnpọ̀-ìtàn rẹ̀ tí ó fara sin.
- Wọn rí àhunpọ̀-ìtàn inú eré-oníṣe ọdún ìbílẹ̀ tó wà lábalalábala, tí a sì ń fi ìlò àmì gbé kalẹ̀ yìí gẹ́gẹ́ bíi àbùdá irú eré-oníṣe bẹ́ẹ̀, tí ó sì kójú òṣùwọ̀n láti gba ọdún ìbílẹ̀ gẹ́gẹ́ eré-oníṣe.
- Bákan náà ni wọn kò ka àìsí ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì tó lọ títí sí ohun bàbàrà kan dàbí alárà.
- Ògúndèjì nínú àwọn àfikún rẹ̀ sí àwọn àwíjàre wọ̀nyí tọ́ka sí i pé lára àṣà ọmọnìyàn ni eré-oníṣe wà. Àṣà kan náà kì í sì í bára mu jákèjádò àgbáyé. Bí àpẹẹrẹ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ibi gbogbo ni a ti ń jẹun, tí à ń wọṣọ, tí à fọmọ fọ́kọ síbẹ̀ ìlànà tí à ń gbà ṣe àwọn àṣà káríayé wọ̀nyí yàtọ̀tọ̀ láti ẹ̀yà dé ẹ̀yà àti láti orílẹ̀ èdè dé orílẹ̀ èdè. Ìrírí lóríṣiríṣi tí ó yàtọ̀ọ̀tọ̀ láti ibìkan dé ibìkejì ni ohun pàtàkì tí ó sì fa àwọn ìyàtọ̀ náà. Ìdí náà ni a fi lè rí ọdún ìbílẹ̀ tí wọ́n ní àwọn àbùdá ìṣeré gẹ́gẹ́ bí eré-oníṣe kíkún láàyè ara wọn bí a ti sọ tẹ́lẹ̀.

- Ní ti wí pé àṣeyẹ orò àtẹ̀sìn nìkan ni ọdún ìbílẹ̀ jẹ́, Ògúdèjì, nínú àwọn iṣẹ́ rẹ̀ tún tọ́ka sí i pé ní inú àwọn iṣẹ́ ọnà àbáláyé kì í sí ààlà gbòógì lááárín iṣẹ́ ọnà àti ìṣàmúlò rẹ̀. Ní èrò ti Ògúndèjì, ojú àmúwọ̀rọ̀ yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú ohun tí lítíréṣọ̀ jẹ́ ní ilẹ̀ Afííríkà, èyí tí ó gùn lé ìlanà ìṣàmúlò, tí ó sì yàtọ̀ gédégédé sí ti ilẹ̀ Yúróòpù àti Amẹ́ríkà nibi tí ìgbádùn ẹwà ajẹmọ́nà lítíréṣọ̀ fún ìdáraya nìkan ti jẹ wọ́n lógún bí a ti yán an lókè. Ògúndèjì ní ojú àmúwọ̀rọ̀ yìí ló mú kí ìyàtọ̀ wà nínú ohun tí ó jẹ́ eré-oníṣe nínú àṣà àwọn ènìyàn méjèèjì.

- Ògúndèjì tún fi yéni pé ohun tí ó mú wa gba ìjálá sísun, ẹ̀ṣà pípè, Ṣàngó pípè, ẹsẹ Ifá, tí à ńlò nídìí ìsìn àwọn òrìṣà tí wọ́n jẹ mọ́ àti ọfọ̀ tí à ń lò láti fi mú àwọn àbá wa ṣe lórísirísi abbl. gẹ́gẹ́ bíi ewì alohùn náà ni yóò mú kí a gba ìṣeré orò ọdún ìbílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí eré-oníṣe bí ótilẹ̀ jẹ́ pé àń lò ó fún ìsìn àti ayẹyẹ àwọn òrìṣà; ní èrò rẹ̀ kò sí bí ọ̀bọ ṣe ṣe orí tínàkí ò ṣe.

- Ní ìwoye Ògúndèjì èrò Ulli Beier pé àwọn ọlódún ìbílẹ̀ kò rí ará wọn bí eléré bí kò ṣe bí ẹlẹ́sìn kò tọ̀nà. Ògúndèjì ní onímọ̀ àti akẹ́kọ̀ọ́ gẹ́gẹ́ bíi lámèétọ̀ kò nílò ẹnikẹ́ni láti sọ fún wa pé iṣẹ́ ọnà ni iṣẹ́ kan kí á tó ṣèdámọ̀ rẹ̀. Ó ṣàlàyé pé apọfọ̀ kọ́ ni ó sọ fún wa pé ewì ni ọfọ̀ tí òun ń pè kí á tó mọ̀ pé ewì ni. Àwón àbùdá inú rẹ̀ ni a fi ṣèdámọ̀ rẹ̀ bí irúfẹ́ ewì alohùn Yorùbá kan. Bákan náà ni ó sọ pé ọ̀rọ̀ yẹ kí ó rí pẹ̀lú ọdún ìbílẹ̀ àti àwọn orò inú rẹ̀ gbogbo. Àwọn àbùdá ajẹméré oníṣe bíi tíátà àti bíi lítíréṣọ̀ inú wọn tó láti mú kí a rí wọn bí orísi eré-oníṣe kan láàyè ọ̀tọ̀ ti wọn gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ti ṣe ti fi hàn.

## 4.3 "Àwọn ọdún ìbílẹ̀ kan jẹ́ eré-oníṣe, àwọn kan kì í ṣe eré-oníṣe"

- Ọlá Rotimi (1968) ni abẹnu-gan èrò yìí.

- Agbedeméjì àwọn èrò méjì yòókù ni èrò tirẹ̀ wà. Ó gbà wí pé àwọn ọdún ìbílẹ̀ tí ó bá ní àhunpọ̀-ìtàn tààrà nínú, bí ó ti wù kí ó mọ jẹ́ eré-oníṣe. Àwọn tí kò ní irú àhunpọ̀-ìtàn yìí ni ó kóra ró láti pè ní eré-oníṣe.

- Lára àwọn àpẹẹrẹ ọdún ìbílẹ̀ tí ó pè ní eré-oníṣe, tí ó jẹ́ ti Yorùbá, èyí tí ó fi gbe àlàyé rẹ̀ nídìí ni ìran ìsínjẹ ìjàkadì tí ó máa ń wáyé láàrin Olúuwin àti Ajagẹmọ nínú ọdún Ọbàtálá ní Ẹdẹ àti irú ìsínjẹ kan náà tí ó ń wáyé láàrin Ọbalááàyán àti Ọbalúfẹ̀ nínú ọdún Edì ní Ilé-Ifẹ̀.

- Àwọn ọdún ìbílẹ̀ tí kò sí àhunpọ̀-ìtàn nínú wọn rárá tí Rotimi mẹ́nu bà ní ọdún Ẹ̀yọ̀ ní Èkó àti ọdún Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Ó sọ pé ijó lásán ni ó ṣe pàtàkì nínú àwọn irú ọdún ìbílẹ̀ bẹ́ẹ̀. Èrò Rotimi ni pé ìsínjẹ tí ó wà nínú ijó yìí nìkan ni ó lè mú wa fẹ́ pè é ní eré-oníṣe.

## 5.0 Ìsọníṣókí

- Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ṣe àlàyé pé ọ̀nà méjì pàtàkì ni àwọn onímọ̀ pín sí lórí bóyá eré-oníṣe ni ọdún ìbílẹ̀ ní ilẹ̀ Adúláwọ̀ tàbí kì í ṣe eré-oníṣe.
- A fi kún un pé ọ̀nà kẹta tí kò ṣe pàtàkì lọ títí torí ó mú tàkọ́kọ́ méjèèjì lò ni èrò Ọlá Rótìmí.
- A ṣe àlàyé pé àwọn onímọ̀ kìn-ín-ní, tí Molly Mahood léwájú wọn gbà pé àwọn ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ Adúláwọ̀ kì í ṣe eré-oníṣe. A sọ pé lára àwijàre àwọn onímọ̀ yìí ni pé kò sí àhunpọ̀-ìtàn nínú àwọn ọdún ìbílẹ̀ wọ̀nyí.
- Àwọn ọ̀wọ́ onímọ̀ kejì, tí a ní Oyin Ògúnbà léwájú wọn, gbà pé eré-oníṣe ni àwọn ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ Adúláwọ́. Àwíjàre wọn ni pé ìsínjẹ tí ó jẹ́ ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ eré-oníṣe ni àwọn akópa nínú ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ Adúláwọ̀ ń ṣe.
- A jíròrò èrò kẹta tó jẹ́ ti Ọlá Rótìmí a ní kì í ṣe èò tuntun tí ó yàtọ̀ gédégédé sí ti àwọn méjì yòókù. Ọlá Rótìmí gbà ní tirẹ̀ pé ọdún ìbílẹ̀ tó bá ti ní àhunpọ̀-ìtàn tààrà nínú jẹ́ eré-oníṣe nígbà tí èyí tí kò bá ní kì í ṣe eré-oníṣe.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣe àlàyé ọ̀nà méjì gbòógì tí èrò àwọn onímọ̀ pín sí lórìi bóyá eré-oníṣe ni ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ Áfíríkà tàbí kì í ṣe eré-oníṣe?
2. Kín ni àwíjàre Ọlá Rótìmí hàn bóyá eré-oníṣe ni ọdún ìbílẹ̀ tàbí kì í ṣe eré-oníṣe?
3. Ṣàmúlò ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀rí láti fi erò tirẹ hàn lórìi bóyá eré-oníṣe ni ọdún ìbílẹ̀ tàbí kì í ṣe eré-oníṣe?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Adedeji, J. A. 1968. “The place of Drama in Yoruba Religious Observance”, *Odù* 13, No. 1 o.i. 88-94.

Adedeji, J. A. 1972. “Folklore and Yoruba Drama: Ọbatala as A case study”, Dorson R. M. (olóòtú) *African Folklore,* Garden City, Doubleday Co., io.i.321-339.

Beier, U. 1967. "Yoruba Theatre" in Ulli Beier, Ed. Introduction to African Literature: Anthology of Critical Writings on African and Afro-American literature and Oral tradition. Longman Group Limited, 243 – 254.

de Gradt, J. C. 1976. "Root in African Theatre". *African Literature Today,* No.6 o.i. 1-25.

Echerou, M. J. C. 1971. "The Dramatic Limits of Igbo Rituals". Search in African Literatures. Vol 4, no. 1, 24 – 27.

Enekwe, O. E. 1987. *Igbo Masks: The Oneness of Ritual and Theatre*. Federal Ministry of Social Development, Youth, Sports and Culture, Lagos.

Finnegan, R. 1970. *Oral Literature in Africa,* Oxford University Press, Nairobi.

Ibitokun, B. M. 1993. *Dance as Ritual Drama and Entertainment of the Gẹlẹdẹ of Ketu Yoruba Subgroup in West Africa.* Ọbafẹmi Awolọwọ University Press, Ile Ifẹ.

Mahood, M. M. 1966. "Drama in Newborn States", *Presence Afrikaine,* Fol 31 No.60 o.i. 23 - 29

Ogunba, O. 1967. Ritual Drma of the Ijẹbu People: A Study of Indigenous Festivals. Unpublished Ph. D. Thesis, University of Ibadan.

Ogunba, O. 1978. "Traditional African Festival Drama", Ogunba, O Àti Irele A. *Theatre in Africa*. Ibadan University Press, Ibadan, o. i. 3 - 26.

Ogundeji, P. A. 1992. *Yorùbá Drama 1(Eré-oníṣe Yorùbá 1*). Ibadan: Centre for External Studies, University of Ibadan, Ibadan.

Ogundeji, P. A. 1995. 'Yorùbá Drama and Religion: The Pre– and Post– Colonial Situations', *Oríta: Ìbàdàn Journal of Religious Studies,* Vol. xxxvi, Nos. 1 & 2, June/ December, pp. 100 – 112.

Ogundeji, P. A. 2000. *Ritual as Theatre, Theatre as Ritual: The Nigerian Example*, Ìṣẹ̀ṣe Monograph Series, Ìbàdàn cultural Studies Group, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Ogundeji, P. A. 2005. "Forms and Functions of Traditional Theatre Practice in Nigeria" in S. Adémọ́lá Àjàyí ed. *African Culture and Civilization,* Atlantis Books, Ìbàdàn and Ìbàdàn Cultural Studies Group, Ìbàdàn pp. 211 – 245.

Ogundeji, P. A. 2012. ‘Trends and Issues in Yorùbá Festival Studies’, *Ọ̀páǹbàtà*: *LASU Journal of African Studies*. Special Issues on Traditional Religious Rituals in Yorùbáland and Diaspora Vol 5, pp.1 – 22.

Ogundeji, P. A. 2014. *Yorùbá Drama in Time Perspective: An Inaugural Lecture.* Ìbàdàn University Press Publishing House, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Ogundeji, P. A.  àti Fasehun, M. A. 2021. “Insights from Carnivals and Festivals”, in Túndé Akínyẹmi àti Tóyìn Fálọlá (olóòtú) *Handbook of  African Oral Traditions and Folklore,*  Fol. 1., o. i. 105 – 118, Palgrave Macmillan àti Springer Nature, Switzerland.

Ogundeji, P. A.  1995. “Culture Yoruba Drama and Religion: The Pre-colonial and Post-colonial Situations”. *Orita: Ibadan Journal of Religious Studies*. Vol. xxvi. Nos. 1 – 2. 100 – 112.

Rotimi, O. 1968. “The Drama in African Ritual Display”, *Nigeria Magazine*, No 99 o.i. 329-330, ó tún wà nínú Ogunbiyi, Y. 1981 Drama and Theatre in Nigeria: A Critical Source Book, Nigerian Magazine Publication, Lagos.

Ugonna, N. !983.  *Mmonwu: A Dramatic Tradition of the Igbo*. Lagos University Press, University of Lagos, Lagos.

## Ìpín 2: Ìpínsísọ̀rí Àti Ìṣàmúlò Ọdún Ìbílẹ̀ Yorùbá

Àkóónú

1.0 Ìfáárà

2. 0 Èròńgbà Àti Àfojúsùn

3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú

4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4. 1. 0 Ìpínsísọ̀rí

4. 1. 1 Ọdún Ajẹmọ́tàn Ìṣẹ̀lẹ̀ gidi

4. 1. 2 Ọdún Ìkórè Oko

4. 1. 3 Ọdún Ọba

4. 1. 4 Ọdún Ajẹmórò Ìlàkọja/ Ìṣípòpadà

4. 2 Ọrọ̀ Ìfọ̀lúmọ̀ Nínú ọdún Ìbílẹ̀
4. 3 Àwọn Ìṣàmúlò/ Ìwúlò Ọdún Ìbílẹ̀ Mìíràn
4. 4 Ìwọ̀núbọ̀nú Ìpínsísọ̀rí tí a gbìyànjú láti ṣe.
5. 0 Ìsọníṣókí
6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7. 0 Ìwé Ìtọ́kasí,`

## 1. 0 Ìfáàrà

Oríṣìíríṣìí ni àwọn ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ adúláwọ̀ lápapọ̀ àti ti ilẹ̀ Yorùbá ní pàtó. Oríṣìíríṣìí sì ni àwọn ohun tó máa ń ṣe okùnfà àwọn ọdún náà. Àwọn ohun tó máa ń pilẹ̀ àwọn ọdún wọ̀nyí ló máa ń sábàá tọ́ka sí irú ọdún tí ọdún ìbílẹ̀ kan jẹ́, àwọn. Àwọn ọdún ìbílẹ̀ kan wà tó jẹ́ pé ìṣẹ̀lẹ̀ gidi pàtàkì kan tàbí òmíràn ló pilẹ̀ ìtàn wọn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ló jẹ́ pé èròǹgbà kí ìlú tùbà, kó tùṣẹ, kí àlàáfíà wà nílé, lóko ni ó bí wọn. Orò ìfọ̀lúmọ̀ lẹ́yìn ìṣẹ̀lẹ̀ búburú kan lè padìí ọdún ìbílẹ̀ mìíràn. Ó dájú pé ìrántí àwọn òkú ọ̀run wà lára ohun pàtàkì tí ó bí ọdún eégún àti ọdún orò náà. Àyẹ́sí, ìdálọ̀lá àti ìfìmọrírì hàn sí ọmọ onílẹ̀ tó ti papòdà, tó sì gbélé ayé ṣe rere wà lára ohun pàtàkì tí wọn fi dá ọdún Ẹ̀yọ̀/ Òrìṣà Adímú sílẹ̀ lÉkòó. Ọ̀kan-ò-jọ̀kan irúfẹ́ àwọn ìdí báyìí ló máa ń pilẹ̀ ọdún ìbílẹ̀. Ìpínsísọ̀rí àwọn ọdún ìbílẹ̀ wọ̀nyí ni ó jẹ wá lógún níní Ìpín kejì yìí, ìlànà ìwúlò/ ìṣamúlò wọn ni a sì gùn lé fún ìpínsísọ̀rí náà.

## 2. 0 Èròńgbà Àti Àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóó le ṣe:

- Àlàyé òṣùwọ̀n pàtàkì tí a fi ṣe ìpínsísọ̀rí ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá
- Ìdámọ̀ oríṣìíríṣìí àwọn ìsọ̀rí ìsọ̀rí tí a pín ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá sí.
- Àlàyé ṣókí ṣókí nípa àwọn ìsọ̀rí ìsọ̀rí náà.
- Àlàyé nípa ìṣamúlò/ ìwúlò àwọnn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá.
- Àwọn àpẹẹrẹ oríṣìí ìsọ̀rí ọdún ìbílẹ̀ tí a jíròrò lé lórí.

## 3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú

1. Òṣùwọ̀n pàtàkì wo ni a fi ṣe ìpínsísọ̀rí ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá?

2. Ṣe ìdámọ̀/ Dárúkọ àwọn ìsọ̀rí ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá tí o mọ̀.
3. Irè oko wo ni àwọn Yorùbá máa ń ṣọdún rẹ̀? Dárúkọ ìlú mẹ́rin tí o mọ̀ tí wọ́n tí í máa ṣe ọdún ìkórè náà.?

## 4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

## 4. 1. 0 Ìpínsísọ̀rí Ọdún Ìbílẹ̀ àti ìwúlò wọn

- Òríṣìíríṣìí ni àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá, oríṣìíríṣìí sì ni àwọn ipa tí àwọn ọdún ìbílẹ̀ wọ̀nyí máa ń kó ní àwùjọ.
- Ògúndèjì àti Fasehun (2021) ti ṣe àlàyé nípa oríṣìíríṣìí ìṣàmúlò àti ipa tí àwọn ọdún ìbílẹ̀ máa ń kó láwùjọ àwọn adúláwọ̀ Áfíríkà lapapọ̀. Iṣẹ́ àjùmọ̀ṣe àwọn onímọ̀ méjì wọ̀nyí ni a fi ṣe àtẹ̀gùn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.
- Wọ́n fi yé wa nínú ọ̀rọ̀ wọn pé a lè lo àwọn ìwúlò àwọn ọdún ìbílẹ̀ wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí òṣùwọ̀n/ láti pín wọn sí ìsọ̀rí ìsọ̀rí. Ìṣoro kan tí wọ́n ní ó wà nínú pínpín àwọn ọdún náà sí ìsọ̀rí ìsọ̀rí ni ti pípọ̀ tí wọ́n pọ̀ jaburata àti pàápàá ti wí pé kò sí ọdún ìbílẹ̀ kan tí ó ní mọ ní ẹyọ ìwúlò kan ṣoṣo.
- Lọ́pọ̀ ìgbà, ẹyọ ọdún ìbílẹ̀ kan ṣoṣo a máa ní ìṣàmúlò mejì, mẹ́ta, mẹ́rin tábí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Èyí tí ó bá lọ̀ọ̀rìn jù lọ nínú àwọn ìṣàmúlò náà ni a óò máa fi perí ọdún ìbílẹ̀ náà. Ṣùgbọ́n èyí lè ṣoro ó mọ̀ nígbà mìíràn. A óò tún gbé èyí yẹ̀ wò ní kíkún ní tòtò ìparí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.
- Nípa lílo òṣùwọ̀n ìṣàmúlò àwọn ọdún ìbílẹ̀ náà, ìsọ̀rí ìsọ̀rí mẹ́rin tí ó yanjú tí Ògúndèjì àti Fásehùn tọ́ka sí ni: ọdún ajẹmọ́tàn-ìṣẹ̀lẹ̀ gidi, ọdún ìkórè-oko, ọdún ọba, ọdún Ìlàkọjá/ Ìṣípòpadà.
- Yàtọ̀ sí àwọn ìṣàmúlò mẹ́rin tí a fi ṣe ìpínsísọ̀rí yìí, a tún ṣe ìjíròrò lórí ìṣàmúlò ọdún ìbílẹ̀ fún fífọ̀lú mọ́ àti àwọn ìṣàmúlò mìíràn bí í, ṣíṣe òdíwọ̀n iye ọdún, ṣíṣe ìrántí àti àpọ́nlé àwọn akọni ìgbààni,

### 4. 1. 1 Ọdún Ajẹmọ́tàn-Ìṣẹ̀lẹ̀ gidi

- Gẹ́gẹ́ bí àlàyé Ògúndèjì àti Fasehun, irúfẹ́ ọdún yìí ni àwọn ọdún tó jẹ́ pé ìṣẹ̀lẹ̀ ajẹmọ́rìírí mánigbàgbé kan, tí ó ṣẹlẹ̀ sí ẹ̀yà tàbí ìran àwọn ènìyàn tó ń ṣe ọdún náà ni ó mú wọn sọ ọ́ di ọdún, tí wọ́n sì ń ṣe àjọyọ̀ ìrántí ní ọdọọdún.

- Irúfẹ́ ìtàn ìsẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ le jẹ́ bí akínkanjú kan ṣe gba àwọn ìran rẹ̀ là ní àkókò ìṣòro kan tàbí òmíràn, ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ìlú. Ó sì le jẹ́ bí àwọn ìran kan ṣe ṣí láti ààyè kan bọ́ sí ààyè mìíràn.
- Àwọn òrìṣà àti akọni ìgbàanì àti àwọn babańlá pẹ̀lú ìyáńlá ni wọ́n máa ń sábàá jẹ́ akọni ẹ̀dá ìtàn inú ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ bẹ́ẹ̀.
- Àpẹẹrẹ irúfẹ́ ọdún yìí ni ọdún Edì ní Ilé Ifẹ̀. Ọdún Edì jẹ́ àyájọ́ àjọ̀yọ̀ bí àwọn ènìyàn Ifẹ̀ ṣe ṣẹ́gun àwọn Ùgbò pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ Mọ̀rèmí Àjàṣorò. Láti rántí ipa ribiribi tí Mọ̀rèmí kó nínú ìṣẹ́gun Ifẹ̀ ló mú àwọn Ifẹ̀ sọ Mọ̀rèmí àti ọmọ rẹ̀ Olúorogbo, tí ó fi rúbọ di àkúnlẹ̀bọ, tí wọ́n sì ń ṣe ọdún rẹ̀ ní Ifẹ̀ títí di òní. Orúkọ mìíràn fún ọdún Edì yìí ni ọdún Mọ̀rèmi.
- Àpẹẹrẹ mìíràn ni ọdún Igogo ní Ọ̀wọ̀, èyí tí wọ́n máa ń ṣe ní ìrántí Ọ̀rọ̀nsẹ̀n, alágbára obìrin, tí ó jẹ́ ayaba Ọlọ́wọ̀ Rẹ̀nrẹ̀ngẹ̀njẹ̀n. Ó jẹ́ ààyò ọkọ rẹ̀ nítorí pé ó lo agbára rẹ̀ láti sọ ọkọ rẹ̀ di olọ́lá, ṣùgbọ́n àwọn orogún rẹ̀ gbógun tì í, wọ́n já àwọn èèwọ̀ rẹ̀, ó sì bínú kúrò lááfin. Wọ́n wá a títí tí wọ́n fi rí i nínú igbó ùlajà tí wọ́n tún ń pè ni igbo Ọ̀rọ̀nsẹ̀n. Ó kọ̀ láti bá wọn padà wọ ìlú, ṣùgbọ́n ó ka òun orò tí wọ́n gbọ́dọ̀ máa fi rúbọ sí òun lọ́dọọdún tí wọ́n bá fẹ́ kí ìlú tòrò. Bẹ́ẹ̀ ni ó ṣe di àkúnlẹ̀ bọ òrìṣà. Ìtàn ìwásẹ̀ nípa Ọ̀rọ̀sẹ̀n yí ni àwọn ìṣeré orò inú ọdún náà dá lé bí Àránsí () ti fi yé wa

## 4. 1. 2 Ọdún Ìkórè-oko

- Iṣẹ́ àgbẹ̀ ni iṣẹ́ abínibí pàtàkì àwọn Yorùbá, iṣu sì ni irè oko pàtàkì jùlọ tí wọ́n máa ń ṣe ọdún rẹ̀ láàrin wọn. Ìdí nìyí ti wọn fi ń pe ọdún ìkórè náà ní ọdún ìjẹṣu. Ìyán ni ounjẹ pàtàkì tí wọ́n máa ń fi iṣu gún. Ọkà, tàbí àmàlà tí ó jẹ́ pé láti ara iṣu náà ni wọn ti máa ń ṣe èlùbọ́ tí wọ́n fi ń rò ó sì ni ó pọwọ́ lé iyan. Ìdí niyí tí wọn fi ń pa òwe pé, "Iyán lounjẹ, ọkà loògùn, àìrí rárá là ń jẹ̀kọ, kẹ́nu má dilẹ̀ ni ti gúgurú."
- Ní ayé àtijọ ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ jẹ iṣu tí wọn kò bá tí ì ṣe gbogbo ètùtù tí óyẹ. Àkókó ìkórè iṣu tuntun yìí ni àwọn Yorùbá máa ń ṣe àwọn ètùtù tàbí orò tí wọn gbà pé ó jẹ́ àìgbọdọ̀ má ṣe; pẹ̀lú ayẹyẹ, tìlù tifọn pẹ̀lú ayọ̀ ńlá sì ni wọ́n máa ń ṣe é. Èyí sì ni ìdí tí ó fi jẹ́ ọdún ìbílẹ̀.

- Lára àwọn ìlù Yorùbá tí wọ́n ti máa ń ṣe ọdún ìjẹ̀ṣu (tuntun) ni Adó Èkìtì, Ìlárámọ̀kín, Ìkẹ́rẹ́ Èkìtì, Òtùn Èkìtì àti àwọn ìlú Èkìtì mìíràn pẹ̀lú Ọ̀wọ̀. Wọn a máa pe ọdún ìjẹ̀ṣu (tuntun) ní ọdún ùdíròókò ni Adó Èkìtì nítorí ìdí igi ùrókò (ìrókò) ńlá tí ó wà láàfin Èwí Adó jẹ́ ibi ìṣeré pàtàkì tí orò ọdun náà ti í máa wáyé. Ọdún ọrẹ̀ ni wọ́n máa ń pe ọdún iṣu tuntun ní Ọ̀wọ̀. Lẹ́yìn tí wọ́n bá ṣe ọdún ọrẹ̀ tán ni wọ́n tó máa ń ṣe ọdún Igogo tí ó gbajúgbajà jù lọ ní ìlú Ọ̀wọ̀.
- Pàtàkì nínú ohun tí wọ́n ń fi ọdún náà ṣe ni láti dúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn òrìṣà àti alálẹ̀ wọn, kí wọ́n sì fi ìmọrìrì hàn sí wọn. Ìdí ni pé wọ́n gbàgbọ́ pé àwọn ni wọ́n ṣe okùnfà ìrè yanturu ọdún náà. Lára àwọn òrìṣà tí ó níí ṣe pẹ̀lú iṣẹ́ àgbẹ̀, tí wọ́n máa ń bọ ní àkókò yí ni Ògún, Òòṣà oko, àti Ẹrinlẹ̀.
- Wọn a tún máa fi ọdún ìjẹ̀ṣu yìí bu ọlá fún ọba ìlú, tí wọ́n gbàgbọ́ pé àkókò rẹ̀ lórí oyè tí ó dára wà lára ohun tí ó ṣokùnfà irè yanturu. Kódà ọba ìlú gẹ́gẹ́ bí áláṣẹ ní í máa léwájú nínú ayẹyé ọdún náà. Ààfin ọba sì ṣe paàtàkì nínú àwọn ibi tí wọ ó ti ṣe ètùtù àti orò ọdún.
- Gẹ́gẹ̀ bí Ògúndèjì àti Fasehun ṣe sọ lára àwọn ìgbésẹ̀ pàtàkì inú ọdún náà ni líla iṣu tuntun, fifi rúbọ sí àwọn òrìṣà, sísè é tàbí sísun un/ fífi gúnyán fún Ọba ìlú àti àwọn àwọn ìjòyè, ṣíṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìwúre pẹ̀lú orin ìlù àti ijó.
- Lẹ́yìn ayẹyẹ yìí ni gbogbo ará ìlú tó ní àǹfàní àti ẹ̀tọ́ láti máa jẹ iṣu tuntun. Ìgbàgbọ́ wọn ni pé bí àwọn bá ṣe gbogbo orò ọdún náà bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ, kò le sí ewu kankan bí àwọn bá bẹ̀rẹ̀ sí níi jẹ tí àwọn sì ń tà nínú irè náà.
- Ayẹyẹ ọdún ìbílẹ̀ yìí tún wà fún sísààmì ìbẹ̀rẹ̀ ọdún tuntun. Kì í ṣe ọdún ìkórè nìkan ni wọ́n fi ń sààmì ìgbà àti àkókò bẹ́ẹ̀. Wọn a máa lo gbogbo àwọn irúfẹ́ ọdún yòókù náà.

### 4. 1. 3 Ọdún Ọba

- Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọba ìlú a máa kó ipa patàkì nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún ìbílẹ̀ ìlú rẹ̀ nítorí pé òun ni ọkọ ìlú, síbẹ̀ ọba kọ́ ni àwọn ọdún ìbílẹ̀ náà dá lé lórí gan an. Àwọn ọdún mìíràn lè dá lórí òrìṣà ìlú, akọni ìgbàanì kan tí ó jẹ́ baba ńlá tàbí ìyá ńlá wọn, ṣùgbọ́n orí ọba tí ó wà lórí àpèrè lọ́wọ́lọ́wọ́ ni ọdún ọba máa ń dá lé.

- Ọdún ọba jẹ́ ọdún tí a fi ń ṣàpọ́nlé àti àyẹ́sí ọba tó wà lórí oyè. Bí ó ṣe jẹ́ pé à ń lo ọdún ajẹmọ́tàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi láti fi ṣe ayẹyẹ àwọn òrìṣà/ akọni tó ti kọjá lọ, ni à ń ṣe àmúlò ọdún ọba láti fi bu ọlá fún, kí á sì bu iyì kún ọba tó wà nípò adarí ní lọ́wọ́lọ́wọ́. Ó ṣe é ṣe kó jẹ́ pé ọba/akọni kan tó ti lọ ni ó dá irúfẹ́ ọdún yìí sílẹ̀ ṣùgbọ́n ohun tó hànde níbẹ̀ ni pé ọba tí ó wà nípò olórí ìlú ní àkókò bágbàmu ni à ń fi ọdún yìí ń ṣe àyẹ́sí.
- Àpẹẹrẹ irú ọdún bẹ́ẹ̀ ni ọdún Bẹẹrẹ ní Ọ̀yọ́ àti Ṣakí, Ojúde Ọba ní Ìjẹ̀bú Òde, ọdún Ọba ní Òǹdó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Ọdún ìbílẹ̀ náà wà fún fifi ẹsẹ̀ àṣẹ ìjọba ọba orí oyè náà múlẹ̀ danindanin, kí àrídájú lè wà pé kò sí ọlọ̀tẹ̀ kankan láàrin tọba tìjòyè, tará ilé tará oko àti ní gbogbo ìlú àmọ̀ná.
- Ìṣàfihan ọláńlá, ìyì, ẹyẹ àti agbára ọba orí oyè náà máa ń wáyé ní àkókò ọdún ọba. Ìkíni, ìjúbà àti ìwárí fún kábíyèsí jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn ohun tí í máa ṣẹlẹ̀ nígbà náà. Gbogbo àwọn jagunjaun, ìjòyè ìlú àti àwọn àwòrò òrìṣà pẹ̀lú àwọn ìṣòwò àti oníṣẹ́ ọwọ́ ní í máa mú ẹ̀bùn ọdún wá, tí wọn yóò máa fi ìdọ̀balẹ̀ àti yíyíkàá kí ọba ní gbàgede àfin ọba, níbi tí ọba gúnwà sí nínú ọláńlá rẹ̀. Àkókò yi ni àwọn ará ìlú máa ń ní àǹfàní láti rí ọba ní ojú korojú.

### 4. 1. 4 Ọdún Ajẹmórò Ìlàkọjá/ Ìṣípòpadà

- Ọdún yìí jẹ́ oríṣìí orò ìlàkọja tàbi ìṣípòpadà. Àwọn orò yìí ni a máa ńṣe nígbà tí ẹnnìyàn bá ń kúrò ní ipò kan bọ́ sí ipò míràn. Márùn-ún irú orò náà tí onímọ̀ kan tí ń jẹ́ Ampin (2003) gbà pé ó ṣe patàkì jùlọ láàrin àwọn adúláwọ̀ ilẹ̀ Afíríkà ni ti: ìkómọjáde/ ìsọmọlórúkọ, ìbalágà, ìgbéyàwó/ ìlọ́kọ, wíwọ ẹgbé àgbà, didi baba-ńlá/ ìyá-ńlá.
- Láti ipò ọmọdé ni ènìyàn tí í ṣipòpadà dí ẹni tí ó dàgbà tí ó sì ti bàlágà. Ìyẹn ni ẹni tí ó tì ó ti gbọn tí ó sì ti di ẹni ọkùnrin tàbí ẹni obìnrin. Káàkiri ìlẹ̀ Áfíríkà ni wọn ti í máa ṣe irú orò ìbálágà tàbí ìmúmawo jíjẹ́-àgbà yií fún àwọn ọmọ tí ó bá ṣẹ̀ṣẹ̀ bàlágà lọ́kùnrin àti lóbínrin, ṣugbọ́n ti àwọn obìnrin ni ó ṣì wà díẹ̀díẹ̀ lóde òní láàrin àwọn ẹ̀yà Yorùbá kan.

- Nígbà tí a bá ṣe iru orò bẹ́ẹ̀ fún ọ̀wọ́ àwọn ọmọ tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ bàlágà lápapọ̀ ni a tó le kà á sí ayẹyẹ ọdún, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé irú ayẹyẹ bẹ́ẹ̀ lè má gbòòrò, kí ó ká ìlú tó ti àwọn ọdún ìbílẹ̀ yòókù. Ọ̀dọ̀ àwọn Yorùbá Ìlà oòrùn Yorùbá ni irú rẹ̀ sì wọ́pọ̀ sí jù lọ. Àwọn ti Ìwọ̀ oòrùn lè ṣe ètùtù fún ọmọbìnrin lábẹ ilé nígbà tí ó bá kọ́kọ́ rí nǹkan oṣù rẹ̀, ṣùgbọ́n wọn kì í sọ ọ́ di ayẹyẹ bí i ti àwọn ti Ìlà oòrùn.
- A rí àpẹẹrẹ ọdún yìí ní àárín àwọn Oǹdó, Ọ̀wọ̀ àti ibìkọ̀ọ̀kan ní Akókó. Ọdún obitun ni wọ́n ń pe é ní Oǹdó, tí wọ́n sì ń pè é ní obitọn ní Ọ̀wọ̀. Ìsúnkì àtí ìgékúrú obìrin tuntun ni orúkọ náà; ìyẹn ni pé ẹni tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ di ọlọ́mọge tàbí ẹni obìnrin. [obìnrin tuntun (a pa /r/ inú ‘obìntun’ jẹ) > obìnin tuntun > (a tún pa /ìn/ inú obìnin jẹ > obin tuntun (a sì gé àpétúnpè tuntun kúrú láti méjì sí ọ̀kan,) > obintun (ìṣàmúlò fáwẹ́lì àìrámúpè ‘i’ dípò ti àránmúpè ‘in’) > obitun. Kíyèsí wí pé ìkan náà ni ìtumọ̀ ‘tuntun’ àti ‘tọntọn’ jẹ́; ẹ̀ka èdè Ọ̀wọ̀ ni ó fa ìyàtọ̀. Wọ́n a sì máa pè irú ọdún náà ní Arigíyà ní Òkèègbé, Ìkàrẹ́ Àkókó.
- Ìpele mẹ́ta gbígbòòrò tí ìṣorò yìí máa ń pín sí ni àkókò: ìṣaájú ìlàkọjá, àkókò ìlàkọjá àti àkókò ẹ̀yìn ìlàkọjá. Àkókò ìlàkọjá kúrò ní ọmọdé bọ́ sí ipò ọlọ́mọgé máa ń jẹ́ àkókò ìyàsọ́tọ̀, tí wọn yóò kó gbogbo àwọn irú ọmọ bẹ́ẹ̀ jọ síbìkan lábẹ́ ìtọ́jú àwọn agbàlagbà tí fún ìtọ́jú arà ọ̀tọ̀, tí wọn óò sì máa dá wọn lẹ́kọ̀ọ́ nípa ipò tuntun tí wọ́n fẹ́ bọ́ sí, gẹ́gẹ́ bí obitun/ ọlọ́mọge tuntun tàbí ẹni tó ṣẹ̀ṣẹ̀ tó ilé ọkọ ọ́ lọ, tó ti tó ó gbé níyàwó. Àkókò ìpalẹ̀mọ́ láti lọ ibi ìyàsọ́tọ̀ yìí ni àkókò ìṣaájú ìlàkọjá, nígbà tí wọ́n bá wà ní ibi ìyàsọ́tọ̀ yí ni àkókò ìlàkọja gan-an. Nígbà tí wọ́n bá kúrò ní ibi ìyàsọ́tọ̀ yí ni àkókò ẹ̀yìn ìyàsọ́tọ̀.
- A lè pe irú orò yìí ní orò ìmúmawo jíjẹ́ ẹni obìnrin. Ọjọ́ mẹ́sàn-án gbáko ni wọn fi ń ṣe orò Obitun ní Oǹdó. Oríṣiríṣi ni orò àti ètùtù inú rẹ̀. Lára rẹ̀ ni ìṣeré orò ìdána, *eyegbe* ní ẹ̀ka èdè Oǹdó, níbi tí wọn ó ti ṣe ìsínjẹ orò ìdána, tí ẹnìkan, ó máa ń sábà jẹ́ obìnrin tí ó múra bí ọkùnrin, yóò ṣe ìsínjẹ ọkọ ìyàwó tí àwọn kan yóò sì ṣe ìsínjẹ ará ilé rẹ̀ láti wá tọrọ ìyàwó (obitun) náà. Orò ìpínùn náà a tún máa wáyé fún obitun náà, kí àwọn ẹgbẹ́run rẹ̀ má baà máa yọ ọ́ lẹ́nu nígbà tí ó bá délé ọkọ tán lẹ́yìnọ̀rẹyìn. (Wo Ìlúyẹmí, O. 2003, àti Ajibádé O. 2009)

- Pàtàkì nínú ẹ̀kọ́ tí wọn máa ń kọ́ ní àkókò ìlàkọjá tàbí ìgbélé ìyàsọ́tọ̀ ni ọ̀rọ̀ ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú ọkùnrin; pàápàá ti pípa ìbálé wọn mọ́ di ìgbà ìgbéyàwó wọn, fún ọkọ orí wọ́n, kí wọ́n má baà kó ìtìjú àìlẹ́gbẹ́ bá òbí àti tẹbí tará wọn lápapọ̀.Wọn tún máa ń kọ́ wọn ní oríṣiríṣi ojúṣe obìnrin lẹ́ẹ̀dẹ̀ ọkọ; kíkó ẹbí ọkọ mọ́ra, bí a ti ń dáná oúnjẹ fún ọkọ (pàápàá iyán gígún nínú orò obitun), ìtọ́jú ilé àti ojúṣe láwùjọ. Lára ẹ̀kọ́ náà sì ni oríṣiríṣi orín àti ijó ìbílẹ̀ náà wà; pàápàá èyí tí wọn yóò fi ṣe ayẹyẹ ìjáde ìgbélé ìyàsọ́tọ̀.
- Ọjọ́ ayọ̀ ìdùnnú àti ayẹyẹ ńlá tí gbogbo àwọn ènìyàn àti olólùfẹ́ wọn sì máa ń bá wọn ṣe ni ọjọ́ ìjáde ìgbélé ìyàsọ́tọ̀ máa ń jẹ́. Èyí ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn sì mọ̀ jù nínú orò náà. Ijó tí àwọn ọlọ́mọge tuntun (obitun) náà máa ń jó pẹ̀lú ìmúra tí ó fi ẹwà àdámọ wọn hàn kamọ̀mọ̀.
- Ní ayé àtijọ ìgbà tí obìnrin bá tó ṣe orò yìí ni ó tó le múra láti lọ sí ilé ọkọ. Wọ́n gbàgbọ́ pé ọdọ́mọbìnrin tí kò bá kópa nínú orò ọdún ìbílẹ̀ yìí, yóò ní ìṣoro nílé ọkọ; pàápàá ti ìbímọ. Ṣùgbọ́n lóde òní ní Oǹdó àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ibi tí wọ́n ṣì ń ṣe é, ayẹyẹ ijó ibẹ̀ nìkan ni wọ́n fi ń dáni lárayá  níbi àríyá. Wọ́n ti sọ ọ́ di ẹgbẹ́ oníjó àṣà ìbílẹ̀.Wọ́n ti yọ gbogbo orò yòókù kúró nítorí ọ̀làjú àti ẹ̀sì ode òní.
- A tún lè rí ọdún ìyàwó láàárín àwọn Sàhó, Odò Ọ̀tìn, Ìṣẹ́yìn, Ògbómọ̀ṣọ́, Ọ̀yọ́ àti àwọn agbègbè rẹ̀ látijọ́ gẹ́gẹ́ bí ọdún ìlàkọjá tàbí ìṣípòpadà. Látijọ́, ọjọ́ kan náà, ní àsìkò ẹ̀ẹ̀rùn ni gbogbo àwọn ọlọ́mọge tí wọ́n bá tó ó gbé níyàwó (ìyẹn ni pé tí wọ́n tó ó lọ ilé ọkọ) máa ń lọ ilé ọkọ.  Ọba ìlú ní í máa dá ọjọ́ yìí tí gbogbo ẹbí tí ó lọ́mọ tó ń lọ ilé ọkọ yóò sì máa palẹ̀mọ́. Àjọyọ̀ tó kárí, tí ó máa ń wàyé ní àkókò náà ni àwọn ènìyàn ṣe kà á sí ọdún. Ọ̀dọ́mọbìnrin tí kò bá rẹ́ni gbé e níyàwó ní àsìkò náà, a máa di ẹ̀ẹ̀mìí kí ó tún tó lọ́kọ. Bí ọdún ìbílẹ̀ gẹ́lẹ́ ni a ṣe ń ṣe é torí pé àti ará ilé àti ará oko ni ẹsẹ̀ wọn máa ń kò láti wá ṣe àjọyọ̀ náà.
- Bákan náà ni ọdún Ayàn ní ìlú Àhàn Èkìtì. Ọdọọdún ni wọ́n ń ṣe ọdún yìí ṣùgbọ́n ọdún kẹsàn-án kẹsàn-án ni àwọn ọ̀dọ́ ìlú náà lọ́kùnrin lóbìnrin máa ń dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́gun. Ìdarapọ̀ mọ́ ẹgbẹ́gun yìí ni àmì pàtàkì láti fi hàn pé àwọn ọ̀dọ́ náà ti kúrò ní ọmọdé àti pé wọ́n ti le ṣe iṣẹ́ ìlú gẹ́gẹ́ bí i dídáàbò bo ìlú àti ogun jíjà. Ní àkókò àjọyọ̀ ọdún yìí àwọn ọ̀dọ́ tó ti dàgbà tó láti ọdún kẹsàn-án sẹ́yìn á dara pọ̀ mọ́

ẹgbẹ́gun, wọn yóò máa na àdá sókè, wọn yóò sì máa jó. Èyí jẹ́ àfihàn pé àwọn náà ti tó ogun ún lọ, wọ́n ti tó ojú ú bọ́.

## 4. 2 Orò Ìfọ̀lúmọ̀ nínú ọdún ìbílẹ̀

- Ṣàṣà ni ọdún ìbílẹ̀ ti kì í ṣàmúlò orò ìfọ̀lúmọ̀. Ìṣamúlò/ ìwúlò rẹ̀ a tilẹ̀ máa lọ́ọ̀rìn nígbà míràn débi wí pé a fẹ́rẹ̀ lè pe gbogbo ọdún tí ó ti jẹyọ ní ọdún ìfọ̀lúmọ̀. Nínú orò ìfọ̀lúmọ̀ ni a ti máa ń ṣe ètùtù fífọ ìlú mọ́ kúrò nínú gbogbo èérí, ìwà ìkà àti gbogbo iṣẹ́ ibi pẹ̀lú àtúbọ̀tán búburú tí wọ́n máa ń fà sáàárín ìlú. Àwọn ìgbésẹ̀ ajẹmórò bí i irúfẹ́ ijó pàtó kan, ìpohùn tàbí ìsínjẹ ìṣe kan tàbí òmíràn a máa wà nínú rẹ̀. Àwọn èyí jẹ mọ́ ìṣeré. Ìrúbọ sí àwọn òrìṣà àti alálẹ̀ fún ìyọ́nú àti ojú rere náà a máa kó ipa pàtàkì jẹ mẹ́sìn. Nípàsẹ̀ ṣíṣe àwọn ètùtù ìrúbọ àti gbígbé àwọn ìgbésẹ̀ ajẹmọ́ṣeré inú orò inú ọdún ìbílẹ̀ tí ó yẹ bẹ́ẹ̀ ni gbogbo ajogun yóò sì fi kúrò láàárín ìlú.
- Àpẹẹrẹ irúfẹ́ orò yìí wà ninú ọdún Òrìṣà Adímú ní ìlú Èkó níbi tí àwọn Ẹ̀yọ̀ aláfẹfẹyẹ̀yẹ̀ yóó ti fi ọ̀páǹbàtà wọn ré gbogbo ibi ààrín ìlú tí wọn óò sì máa fi aṣọ àróplẹ̀ wọn kó gbogbo òfò àti àṣeèrí kúrò ní ààrin ìlú, bí wọ́n ti ń yí ìlú ká látàárọ̀ títí di ọjọ́rọ̀. Nígbà tí ó bá di ìrọ̀lẹ́, wọn óò lọ sí ọ̀gangan ibi tí a tì yà sọ́tọ̀ fún ìṣeré or àṣekágbá náà ní ìdúmọ̀tà tí wọn ó sì tò sóri ìlà ní ọ̀wọ́ mejì, ní ìdojú-kọra pẹ̀lú ọ̀páǹbàtà wọn ní nínà sókè. Nígbà tí Òrìṣà Adímú bá dé yóò gba ààrin wọn kọjá. Gbogbo àwọn Ẹ̀yọ̀ aláfẹfẹ yẹ̀yẹ̀ náà yóò sì máa gbọn ọ̀páǹbàtà wọn lé e lórí ní ìrètí pé gbogbo ibi tí àwọn ti kó ni àwọn ti gbọ̀n lé e lórí yẹn. Òrìṣà Adímú yóò sì gbé gbogbo rẹ̀ rìn wọnú ọ̀sà lọ.
- Orò ìfọlúmọ̀ náà wà nínú Ọdún Edì ní Ilé Ifẹ̀. Ó sì wà nínú ọdún Ọ̀ṣun ní Òṣogbo àti ọ̀pọ̀ ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá mìíràn, bí a ti sọ tẹ́lẹ̀. Nínú ọdún edì àwọn orò mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n jẹ́ orò ìfọ̀lúmọ̀ ni ọ̀fọ̀nràn, pípako dílé olè àti ti ríru ibi lọ kúrò láàrin ìlú. Orò ọ̀fọ̀nràn ní wọ́n fi máa ń ṣíde ọdún Edì Igi ìdáná (tí wọ́n ń pè ní igi ẹtà) ni wọ́n máa ń fi dáná sí ìkòríta ìkòríta àti gbangba iwájú ilé káàkiri ààrín ìlú. Ìgbàgbọ́ wọn ni pé èéfín igi náà tí ń rú túú yóò fín gbogbo àwọn ẹ̀mí burúkú

àti ibi jáde kúrò nílùú. Ní àárin ọdún náà ni pípa oko dílé olè máa ń wáyé. Gbogbo àwọn tí wọ́n bá ti hùwà ìbàjẹ́ kan tàbí òmíràn ni wọ́n máa ń kó koriko àti pàǹtí oríṣiríṣi lọ dà sí ẹnu ọ̀nà ilé wọn tí wọn óò sì máa kọrin láti fi wọ́n ṣẹlẹ́yà àti ẹ̀sín. Púpọ̀ nínú àwọn bẹ́ẹ̀ a sì máa fìtìjú sá kúrò nílùú nítorí rẹ̀. Ríru ibi kúrò láàrin ìlú jẹ́ ara orò àṣekágbá. Tele sì ni orúkọ ẹ̀dá ìtàn tí í máa rù ú. Wọn ó di oríṣiríṣi ìdọ̀tí lé e lórí abọrẹ̀ yóò sì mú un la ìlú kọjá lọ sí igbo Mọrèmi. Bí ó ti ń la ìlú kọja ni àwọn èrò ìworan tí wọn wà lẹ́gbẹ̀ẹ̀gbẹ́ òpópónà yóò máa, wí pé “Yooyóò, Yooyóò yo, ikú yooyóò yo, àrùn yooyóò yo, òfò yooyóò yo”. Tí a tún lè túmọ̀ sí “Kókú lọ, kárùn lọ, kófò lọ”

- Ìbẹ̀rẹ̀ ọdún Ọ̀ṣun ni orò ìwopópó máa ń wáyé. Àtaója, tí ó jẹ́ ọkọ ìlú pẹ̀lú àwọn olorì àti ìjòyè rẹ̀ bíi mélòó kan yóò ṣe ìbẹ̀wò àwọn òpópónà kan láti rí i pé ó mọ́ tónítóní. Àwọn obìnrin yóò ti gba gbogbo ìdọ̀tí ìbẹ̀ mọ́ tónítóní. Èyí sì dúró bí àmì ìfọ̀mọ́ kúrò nínú gbogbo ẹ̀gbin àfojúrí àti àìfojúrí.

## 4. 3 Àwọn Ìṣàmúlò Ọdún Ìbílẹ̀ Mìíràn

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣaájú ìlànà ìṣàmúlò àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá ni a fi pín wọn sí ìsọ̀rí ìsọ̀rí. Bí a bá wò ó àwọn ìwúlò ọdún ìbílẹ̀ tí a ti mẹ́nu bà ni fífi ọdún ìbílẹ̀:

- Sàmì ìṣẹ̀lẹ̀ pàtàkì nínú ìtàn ìrírí àwọn ènìyàn àwùjọ kan.
- Dúpẹ́ ìkórè ohun ọ̀gbìn, pàápàá iṣu lọ́wọ́ àwọn òrìṣà àti alálẹ̀.
- Ṣe ìgbélárúgẹ ọba orí oyè.
- Sàmì ìṣípòpadà láti ipò kan bọ́ sí òmíràn ìlàkọjá.
- Ṣe iṣẹ́ ìfọ̀lúmọ́.
- A sì tún yán an pé a máa ń fi ọdún ìbílẹ̀ sàmì àkókòkò àti ìgbà; ìyẹn ni pé a máa ń lò ó láti fi ka ìye ọdún. A tún ti tọ́ka sí í pé a tún maá ń lò wọ́n nídìí ẹ̀sìn àwọn òrìṣà; láti fi ṣàpọ́nlé wọn kí á sì yẹ́ wọn sí bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ. Bákan náà ni a sọ pé a máa ń lò wọ́n fún ṣíṣèrántí àwọn Babańlá àti Ìyáńlá pẹ̀lú.

- Lára àwọn ìwúlò/ ìṣàmúlò míràn tí Ògúndèjì àti Fasehun tún mẹ́nu bà nínú iṣẹ́ wọn ni ìṣọkan gbogbo ènìyàn láwùjọ. Ní àkókò ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún ìbílẹ̀ tará ilé, tará oko, tóníle tàlejò ní í máa á péjú pésẹ̀ láti ṣàjọyọ ọdún.
- Àwọn onímọ̀ wa méjì yìí tún fi yé wa pé ìdánilárayá tàbí ìgbafẹ́ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn ìwúlò/ ìṣámúlò tí ó hàn gbangba nínú ọdún ìbílẹ̀. Wọ́n tọ́ka sí i pé àkókò tí kò bá sí iṣẹ́ lóko dàbí alárà ni wọn máa ń sábàá ṣe àwọn ọdún náà àti wí pé gbogbo àbùdá ìjẹmọ́nà inú wọn ní ó mú kí ó wúlò fún ìgbafẹ́ dáradára.

## 4. 4 Ìwọ̀núbọ̀nú

Bí a ti sọ tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀, ọdún ìbílẹ̀ kan a máa ní ju ìṣàmúlò kan ṣoṣo lọ, bẹ́ẹ̀ sì ni àwọn ọdún ìbílẹ̀ pọ̀ ní oríṣiríṣi. Nítórí àwọn yìí ni ìlò òdiwọ̀n ìṣàmúlò àwọn ọdún ìbíilẹ̀ náà fún pínpín wọn sí ìsọ̀rí ìsọ̀rí fi nira. Ògúndèjì àti Fáséhùn pàápàá mẹ́nu bà á nínú ìṣẹ́ àjọṣe wọn.ro ó mọ̀ nítorí ìṣàmúlò méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ lè jọ lọ̀ọ̀rìn bákan náà, kí wọn jọ mú ọgba. Ní irú àsìkò yìí, a nílò láti ṣẹ̀wádìí lọ́wọ́ àwọn ọlọ́dún ìbílẹ̀ nípa èyí tí ó ṣe pàtàkì jù lọ ninú gbogbo àwọn ìwúlò inú ọdún ìbílẹ̀ bẹ́ẹ̀. Bí àpẹẹrẹ òrò ìfọlúmọ inú ọdún Edì àti Òrìṣà Adímú lọ̀ọ̀rìn débi pé wọ́n ń bá àwọn ìṣàmúlò mìíràn ta kànǹgbọ́n. Ìwádìí ni ó jẹ kí á mọ̀ pé Mọrèmí gẹ́gẹ́ bí akọnibìnri ni wọ́n ń fi ọdún Edì ṣèránti àti àpọ́nlé rẹ̀. ìwádìí ni ó sì jẹ́ kí á mọ̀ pé ọmọ Èkó tí ó ti papòdà ni wọ́n ń fi ọdún Edì ṣe àṣeyẹ ìsọdi babańlá fún. Nítorí náà ipò kejì ni orò ìfọ̀lúmọ̀ inú wawọn ọdún méjèèjì yóò wà lórí ìpele àwọn ìṣàmúlò ọdún náà.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ṣe ìpínsíọ̀rí àwọn ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá sí ọ̀nà mẹ́rin gbòógì nípa lílo ìṣàmólò wọn. Àwọn ọ̀nà mẹ́rin náà ni: ọdún ajẹmọ́tàn-ìṣẹ̀lẹ̀ gidi, ọdún ìkórè-oko, ọdún ọba, ọdún Ìlàkọjá/ Ìṣípòpadà níbàámu pẹ̀lú bí Ògúndèjì àti Fasehun, (2021) ti pín wọn. A tún mẹ́nu ba àwọn ìṣàmúlò ọdún ìbílẹ̀ mìíràn pàápàá ti ìfọ̀lúmọ̀. A ṣe àlàyé àti àpẹẹrẹ díẹ̀díẹ̀ nípa wọn. Ní ìparí a jíròrò lórí ìwọ̀núbọnú tí ó wà nípa ìpínsísọ̀rí náà. A tọ́ka sí i pé pípọ̀ yanturu tí wọn pọ̀ àti A mẹ́nu bà á pé ọdún ìbílẹ̀ kan ṣoṣo máa ń ní ju ìṣàmúlò kan lọ àti pé ogunlọgọ̀ tí àwọn ọdún náà jẹ́ kò ló jẹ́ atọ́kùn ìṣoro ìwọ̀núbọ̀nú tí óeà náà.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Kín ni ìdí tí ìwọ̀núbọ̀nú fi wà nínú ìpínsísọ̀rí ọdún ìbílẹ̀ Yorùbá?
2. Lo àpẹẹrẹ kan láti ṣe àlàyé pàtàkì orò ìfọ̀lúmọ̀?
3. Dárúkọ oríṣi orò ìṣípòpadà mẹ́ta tí o bá mọ̀, kí o sì ṣe àlàyé ọkan ní kíkún.
4. ṣe àlàyé ohun tí ọdún ọba wà fún láàrin àwọn Yorùbá.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Ajíbádé, O. 2009. *Finding Femail Voice: A Sociocultural Appraisal of Yorùbá Nuptial Poetry*, Rudiger Koppe Verlag, Cologne.

Àránsí, A. O. 2016. *Ojú Àmúwayé Yorùbá ní Ìlànà Eré-Oníṣe Nínú Ọdún Igogo ní Ìlú Ọ̀wọ̀.*Spectrum Books Ltd., Ibadan

Ìlúyẹmí, O. 2003 *Ondo Traditions and Culture: The Female Angle*, Cornerstone Publishers, Ondo.

Ògúndèjì, P.A. 2000. *Ritual as Theatre, Theatre as Ritual: The Nigerian Example*. Ibadan Cultural Studies Group, Ìbàdàn.

Ògúndèjì, P. A. àti Fáṣẹhùn, M. A. (2021) "Insights from Festivals and Carnivals", Akintunde Akinyẹmi àti Toyin Falọla (olóòtú) *The Palgrave Hand Book of African Oral Traditions, and Folklore*. Fol. 1, o. i. 105 – 118. Palgrave Macmillan and Springer Nature, Switzerland.

Ampin, M. 2003. The Five Major African Initiation rites, htpp://www.manuampin.com/AfricanInitiationrites.htm


# Ìpín 3: Eégún Aláré: Orúkọ, Ìgbéǹde àti Ìdàgbàsókè

Àkóónú


1. 0 Ìfáárà
2. 0 Èròńgbà
3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú
4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4. 1 Orúkọ
4. 2. 0 Ìgbéǹde àti Ìdàgbàsókè
4.2. 1 Ayé aláàfin Ṣàngó
4.2. 2 Ayé aláàfin Òfinràn
4.2. 3 Ìtàn Olúgbẹ̀ẹ́ Àgan

4.2. 4 Ayé aláàfin Abíípa (Ọba Mọ́rọ̀)

4. 3 Láméètọ́
5. 0 Ìsọníṣókí
6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7. 0 Ìwé Ìtọ́kasí

1. 0 Ìfáárà

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe yán an nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí a ti ṣe síwájú, àríyànjiyàn wà lórí bóyá ọdún ìbílẹ̀ ilẹ̀ Áfíríkà (pàápàá tilẹ̀ Yorùbá) jẹ́ eré-oníṣe. Kò sí irúfẹ́ àríyànjiyàn yìí nípa eégún aláré. Oríṣìíríṣìí ni orúkọ tí àwọn ènìyàn ti lò láti fi pe àwọn eléégún tó ń ṣe eré wọ̀nyí láti ìgbà àtijọ́ wá. Lótìítọ́, kò sí àríyànjiyàn nípa bóyá eré-oníṣe ni eégún aláré ṣùgbọ́n àríyànjiyàn oríṣìíríṣìí wà nípa àwọn ìtàn tó wà lórí ìdìdelẹ̀ eégún lápapọ̀ àti ti ìjẹyọ pẹ̀lú ìdàgbàsókè eégún aláré ní pàtó. Lára àwọn tí ó sọ ọ̀rọ̀ kan tàbí méjì lórí ìgbéǹde eégún lápapọ̀ àti eégún aláré ní pàtó ni Johnson (1921: 160), Babalọla (1966: 32 – 34), Adedeji (1969 àti 1972) àti Babayẹmí (1980), ṣùgbọ́n àlàyé Adédèjì ni a ó mú lò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí torí ó tẹnpẹlẹ mọ́ ọ̀rọ̀ eégún aláré ju àwọn yòókù lọ. Àwọn ìsọ̀rí orí ọ̀rọ̀ tí a pín ìjíròrò Adédèjì sí lórí ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè eégún aláré ni: Ayé Ṣàngó, Ayé Òfinràn, Ìtàn Olúgbẹ̀ẹ́ Àgan, Ayé Ọba Mọ́rọ̀, àti Láméètọ́ iṣẹ́ Adédèjì.

2. 0 Èròńgbà
Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó ti lè ṣe àlàyé:

- Àwọn oríṣiríṣi orúkọ tí àwọn onímọ̀ ti fi pe eré àwọn eégún aláré.
- Ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè eégún aláré gẹ́gẹ́ bí Adédèjì (1969 àti 1992) ṣe gbé e kalẹ̀.
- Àwílé lórí àgbékalẹ̀ Adédèjì nípa Ìgbéǹde àti Ìdàgbàsókè àti ìgbéǹde eégún aláré.

3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú

i. Sọ àwọn oríṣìíríṣìí orúkọ mẹ́ta tí o mọ̀, tí àwọn onímọ̀ ti fi pe àwọn eégún tí í máa gbé eré káàkiri láti ibìkan dé ibòmíràn ní ilẹ̀ Yorùbá.
ii. Dárúkọ àwọn aláàfin Ọ̀yọ́ mẹ́ta tí ìtàn ìgbéǹde ìṣeré àwọn eléégún agbéréká tí Adédèjì (1969) sọ rọ̀ mọ́.

iii. Ta ni Olúgbẹ̀ẹ́ Agan? Kín sì ni ipa tí ó kó nínú ìṣeré eégún aláré níbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Eégún Aláré: Orúkọ

- Oríṣiríṣi ni orúkọ tí àwọn onímọ̀ ti mú lò láti fi pe àwọn eégún Yorùbá tí í máa ṣe eré oríṣiríṣi káàkiri láti ìletò dé ìletò, abúlé dé abúlé àti láti ìlú dé ìlú nínú iṣẹ́ wọn. Pàtàkì lára rẹ̀ ni eégún agbégijó, eégún alárìnjó, eégún apidán àti eégún aláré. Ọkan tí wọn kì í sàbà lò ṣugbọ́n tí wọ́n máa ń fi pe àwọn eléégun náà láwùjọ ni eégún lábalà.
- Ulli Beire (1964) ni ó tẹra mọ́ ìṣàmúlò agbégijó ní tirẹ̀. Bí Ògúndèjì (2000) ṣe fi hàn, Adédèjì (1969 àti nínú àwọn iṣẹ́ rẹ̀ míràn) ní ó fara mọ́ ìṣàmúlò eégún alárìnjó, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé òun fúnra rẹ̀ tọ́ka sí i pé orúkọ ìtàbùkù ni orúkọ yìí jẹ́. Ó sọ nínú iṣẹ́ rẹ̀ (1978: 34) pé orúkọ náà ń tọ́ka sí wọn bí alárìnkiri, aláìníkanánṣe tàbí olóòrayè àti aṣagbe-jẹun. Götrick (1984) ló yan ìṣàmúlò eégún apidán láàyò nínú iṣẹ́ rẹ̀.
- Àwọn eléégún wọ̀nyí náà mọ̀ pé àwọn ènìyàn máa ń fi àrìnká tàbí àrìnjó tí àwọn ń ṣe tàbùkù àwọn ni bí Adédejì ṣe tọ́ka sí i, ṣùgbọ́n wọn kò bíkítà nítorí rẹ̀. Àwọn gan-an a tilẹ̀ máa mẹ́nu bà á nínú ẹ̀ṣà pípè wọn:

  Ìyá ló kọ́ mi lédè
  Mo sì mèdè
  Bàbá ló mà kọ́ mi lẹ́ṣà
  Mo mọ̀ ọ́n wí
  Mo mú lẹ́nu ó jabẹ lọ
  Mo ṣòwò ètè rọjà Akèjì
  Òwò tí mò ń ṣe
  Nìyá kọ̀ mí sí
  Baba ló gbé mi lórí ẹṣin...

- Nínú àyọlò yìí, eégún alárìnjó tó pẹ̀ṣà náà jẹ́ kó yéni pé ajẹbí lẹ́ṣà pípè jẹ́ fún òun. Ó tẹ̀ síwájú pé ẹ̀ṣà tí òun mọ̀ ọ́n pè yìí ló mú òun di ìlúmọ̀ká tí òun sì kíwì dé ọjà Akèjì.

Ó ṣàfikún pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìyá kò náání òun nítorí òwò àrìnká tí òun ń ṣe, baba òun baba òun mọ rírì rẹ̀, ó sì ń ṣàpọ́nlé òun. Èyí ni wọn kìí fi í bìkítà nípa ìtàbùkù náà.

- Ìṣàmúlò àwọn oríṣiríṣi ìbòjú (gàrétà) àfigigbẹ́ àti àwọn ère mìíràn tí wọ́n máa ń gbé rù ní àkókò ìṣeré ijó wọn ni ó mú kí wọ́n pè wọ́n ní agbegijó. Bí àwọn eégún yìí ṣe máa ń gbé ìṣeré wọn káàkiri, láti ibìkan dé ibòmíràn, tí wọn yóò sì máa ń jó papọ̀ nínú ìṣeré wọn ni àbùdá pàtàkì tí àwọn ènìyàn wò mọ́ wọn lára tí wọ́n fi pè wọ́n ní alárìnjó. Bákan náà sì ni ó jẹ́ pé idán pípa tí ó jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára ọnà ìṣere wọn tí àwọn olùwòran máa ń gbádùn púpọ̀púpọ̀ ni ó ṣe atọ́nà ìṣàmúlò orúkọ eégún apidán. Ṣíṣàmúlò aṣọ ìṣeré láti fi dárà lójú agbo eré ló mú gí ọ́n tún máa pè wọn eégún náà ní eégún alábalà. Bóyá orúkọ mìíràn tí wọ́n tún máa ń pe aṣọ ìṣeré wọn (àwọn ẹ̀kú/ agọ̀ eégún níńlá níńlá tí wọ́n ní aràbarà àwọ̀) tí wọ́n fi ń jó ni àbalà.
- Gbogbo àwọn orúkọ mẹ́rẹ̀ẹ̀rin tí à ń gbé yẹ̀wò lọ́wọ̀lọ́wọ̀ wọ̀nyí ń fúnka mọ́/ tẹnu mọ́ ìkan tàbí mejì nínú gbogbo àwọn ọnà ìṣeré àwọn eléégún náà ni agbégijó ń tẹnu mọ́ ìbòjú onígi lílò àti ijó jíjó, alárìnjó ń tẹnu mọ́ ìgbéréká àti ijó jíjó, apidán ń fòté lé idán pípa, lábalà ń peàkíyèsí sí ìlò aṣọ ìṣeré aláràbarà. Kò sí èyí tí ó kógo já láti pe àkíyèsí sí gbogbo ọ̀nà ìṣeré wọn lápapọ̀ bíi eégún aláré. Èyí tí ó wù kí ó jẹ́ nínú ọnà ìṣeré wọn, ìbáà ṣe ẹ̀ṣà pípè, òkìtì títa, ijó jíjó, orin kíkọ, idán pípa, ìbòjú lílò, gbíeré ká, aṣọ eré aláràbarà lílò, eré ṣiṣe kan náà ni gbogbo wọn jẹ́, tí wọ́n sì wà fún. Ìdí nìyí tí àwa nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí fi yan orúkọ eégún aláré láàyò. Orúkọ yìí ni àwọn eléégún náà fúnra wọn máa ń lò láti fi pe ara wọn jù lọ. Orúkọ náà kógo já ju gbogbo àwọn orúkọ yòókù lọ.

## 4. 2. 0 Eégún Aláré: Ìgbéǹde àti Ìdàgbàsókè

- Ọ̀rọ̀ Ìgbéǹdé àtìdàgbàsókè eégún aláré jẹ mọ́ ìtàn Ọ̀yọ́ ilé. Ìdí nìyí tí orúkọ àwọn aláàfin Ọ̀yọ́ pàtàkì kan fi jẹ yọ nínú àwọn àlàyé wa ní ìhín.
- Nínú àwọn àlàyé rẹ̀, Adédèjì ṣe àmúlò ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi, ìtàn ìwáṣẹ̀ látinú ẹsẹ ifá àti oríkì láti ṣe àgbékalẹ̀ ìtàn ìgbéǹde àtìdàgbàsókè eégún aláré láti inú orò ìṣẹ́kú. Àwọn ìsọ̀rí tí Adédèjì (1969) sì pín ìtàn ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè eégún aláré sí ni Ayé Ṣàngó, Ayé Òfinràn, Ìtàn Olúgbẹ̀ẹ́ Àgan àti Ayé Ọba Mọ́rọ̀.

### 4. 2. 1 Ayé Ṣàngó

- Adédèjì ṣe àlàyé pé egúgún ti wà tẹ́lẹ̀ rí ní Ilé-Ifẹ̀ gẹ́gẹ́ bí oríṣìí orò ajẹmẹ́sìn kan kí aláàfin Ṣàngó tó wá sọ ọ́ di ohun tí ó fi ń ṣe ìrántí Ọ̀rànmíyàn tí ó jẹ́ bàbá rẹ̀ ní òde Ọ̀yọ́. Èyí ni pé Ṣàngó ni ó dá orò ìṣẹ́kùú sílẹ̀; òkú Ọ̀rànmíyàn sì ni a kọ́kọ́ fi eégún fà. Àwọn kan gbàgbọ́ pé láti ilẹ̀ Tápà níbi tí a ti ìyá rẹ̀ ti ṣẹ̀ ni Ṣàngó ti mú àṣà yìí wọ Ọ̀yọ́.
- Barà ni wọ́n ti máa ń ṣe orò ìṣẹ́kùú yìí ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pl yìí. Ìyá Mọdẹ tí ó jẹ́ ọkàn nínú àwọn àgbà obìnrin tí ó wà láàfin ni ó sì jẹ́ alákòóso ètò náà.
- Nígbà tí ó ṣe àṣà òkú ṣíṣẹ́ di ohun tí gbogbo ìlú náà ń ṣe; inú káà ni àwọn ará ìlú tí ó kọ́ àṣà yìí sì ti máa ń ṣẹ́kùú nígbà náà.
- Títí di òní ni wọ́n ń ṣe orò ìṣẹ́kùú, pàápàá gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan nínú orò àṣekágbá ìsìnkú àgbà ọ̀jẹ̀.
- Orúkọ mìíràn fún orò ìṣẹ́kùú ni òkúfífà/ìfàkú.

### 4. 2. 2 Ayé Ọ̀finràn

- Ayé aláàfin Ọ̀finràn ni egúngún di awo àti apá kan lára ọ̀nà ìṣèjọba ìlú Ọ̀yọ́. Ohun tó mú èyí rọrùn ni ti àwọn ìran eléégún méjì (ìran Ìgbórí àti Ọ̀lọ́bà) tí ó wá láti ilẹ̀ Tápà sí Ọ̀yọ́.
- Aláàfin Ọ̀finràn fi lára wọn jẹ oyè, wọ́n sì ń ṣe ètò eégún fún un. tí ó wá Láti ìran inú ìran Ìgbórì ni ó ti yan Alápinni tí ó fi jẹ olórí àwọn eléégún pátápátá. Ipò yìí sì sọ óAlápinni di ọ̀kan lára àwọn Ọ̀yọ́mèsì, oyè ìṣèlú ajẹmẹ́sìn ni oyè náà. Ológbo tí ó wá láti ìran Ọlọ́bà ni ó sì fi jẹ oyè aṣàkóso ìṣorò àti eré ṣíṣe fún ọba. Àkókò tí eégún gbòòrò báyìí, tí ó di apá kan ìṣèlú àti ọ̀nà ìdánilárayá fún ọba ni eégún di ọdún ìbílẹ̀.

### 4. 2. 3 Ìtàn Olúgbẹ̀ẹ́ Àgan

- Ìtàn Olúgbẹ̀ẹ́ Àgan yìí jẹyọ láti inú ẹsẹ Ifá. Láti inú ẹsẹ inú àmúlù odù Ọ̀wọ́nrínsẹ̀ tí kíkì rẹ̀ bẹ̀rẹ̀ báyìí ni Adédèjì ti mú ìtàn Olúgbẹ̀ẹ́ Àgan:

Arúkú
Arùkú

Arùkú-rọjà-má-tà
Òkú tá a gbé rọjà, tí kò tà
Òun la tún gbé wálé
Tá a dáṣọ bò
Tá ń pè léégún
A dífá fún Ọ̀wọ́nrín Ìsanyín
Tó kú tí àwọn ọmọ rẹ̀
Kò rówó sin ín.

- Nínú àlàyé ẹsẹ ifá yìí, Arúkú tí ó jẹ́ àrẹ̀mọ Ọ̀wọ́nrín Ìsanyín rolé lẹ́yìn ikú bàbá rẹ̀, ó sì di Ológbìn-ín, èyí tí ó sọ ọ́ di ológbo ọba. Ìyámọ̀ṣe, tí ó jẹ́ ìyàwó Arúkú kò rí ọmọ bí. Lọ́jọ́ kan, Ìyámọ̀ṣe lọ sí odò, irò, ẹ̀yà ìnàkí kan kì í mọ́lẹ̀, ó sì bá a lò pọ̀. Ó sá lọ sí ọ̀dọ̀ Ọlọ́pọndà tí ó jẹ́ bàbá rẹ̀ nígbà tó ṣe àkíyèsí pé ìbálòpọ̀ náà doyún, níbẹ̀ ni ó sì bí ọmọ ọkùnrin kan sí. Ọmọ yìí jẹ́ ṣènìyàn-ṣẹranko nítorí pé láti ìbàdí rẹ̀ sí òkè ló jọ tí ènìyàn, ìbàdí rẹ̀ sí ìsàlẹ̀ jẹ́ ti irò. Lẹ́yìn tí ó bímọ tán, bàbá rẹ̀ ni kí ó padà sí ọ̀dọ̀ ọkọ rẹ̀ ṣùgbọ́n nígbà tó dé ojú ọ̀nà, ó gbé ọmọ tó bí náà sínú igọ̀ igi kan nínú igbó. Ato tó jẹ́ aya Ìgògó ló rí ọmọ náà, òun àti ọkọ rẹ̀ sì lọ sọ ní ààfin.
Ìyámọ̀ṣe jẹ́wọ́ nígbà tí aje ọ̀rọ̀ náà ṣí mọ́ ọn lórí.
- Ológbìn-ín sì dáfá láti mọ ìgbésẹ̀ tí ó yẹ kí ó gbé. Ifá ní kí wọ́n rú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àtòrí, àkàrà àti ẹ̀kọ kí wọ́n sì lọ gbé ọmọ náà wálé, pé bàbá rẹ̀ tí wọ́n ti gbé sọnù sígbó, tipẹ́tipẹ́ ni ọmọ náà. Nígbà tí wọ́n lọ gbé ọmọ yìí, tí a mọ̀ sí Olúgbẹ̀ẹ́ Àgan, Ògògó ni ó ru ẹ̀kú tí wọ́n fi gbé e wálé. Ato sì ni wọ́n pè kí ó wá máa tọ́jú ọmọ náà, Ògògó máa ń lọ bẹ̀ ẹ́ wò lóòrèkóòrè. Èyí ló mú wọn máa pè é ní “alágbọ̀ọ́ wá, bàbá tó mọ awo.” Ọ̀rọ̀ yìí ni àwọn ènìyàn pè títí tó di “alágbààá, baba maríwo.”
- Àwọn tó rí ọmọ náà nígbà tí wọ́n ń gbé e bọ̀ ni wọ́n ń sọ pé Egungun òkú tí wọ́n lọ gbé náà gún, pé eegun náà gún gan-an ni. Láti inú gbólóhùn yìí ni egúngún ti jẹyọ. Olúgbẹ̀ẹ́ Àgan kì í jáde kúrò ní ààfin àyàfi ní àkókò ọdún eégún nígbà tí ó máa ń ru ẹ̀kú ilé bàbá rẹ̀. Torí pé ṣènìyànṣẹranko ni, ó mọ òkìtì í ta ju àwọn tó bá lẹ́nu eré lọ. Báyìí ni ó di gbajúgbajà òṣèré.

### 4. 2. 4 Ayé Ọba Mọ́rọ̀ (Abíípa)

- Ayé Ọba Abíípa ni Adédèjì tọ́ka sí pé eégún aláre dìdelẹ̀ gan-an, tí ó sì di ìṣeré kan àrà ọ̀tọ̀ fún ìdánilárayá láàfin. Ọba Abíípa fẹ́ kó Ọ̀yọ́ kúrò ní Ìgbòho padà lọ sí Ọ̀yọ́ Àjàká láti mú ìpinnu baba rẹ̀ ṣẹ, ṣùgbọ́n inú àwọn Ọ̀yọ́mèsì kò dùn sí ìgbésẹ̀ yìí nítorí pé wọ́n ti ní dúkìá rẹpẹtẹ ní Ìgbòho; wọn kò sì ṣetán láti padà sí Ọ̀yọ́ Àjàká. Alápinni bá àwọn Ọ̀yọ́mèsì yòókù lẹ̀dí àpò pọ̀, wọ́n sì rán àwọn abirùn mẹ́fà lọ sí Ọ̀yọ́ Àjàká láti lọ dẹ́rù ba àwọn tí aláàfin rán lọ ṣe ètùtù sí ibẹ̀ kí ìgbésẹ̀ kíkópadà náà le jẹ́ àṣeyege.
- Àṣìrí ìgbésẹ̀ Alápinni yìí tú sí ọwọ́ Ológbìn-ín (Ológbo ọba), ó sì ṣòfófó fún Aláàfin Abíípa. Aláàfin ránṣẹ́ lọ kó àwọn ẹni òrìṣà mẹ́fẹ̀ẹ̀fà náà, ó sì mú kí wọn ṣe ìsínjẹ bi wọ́n ṣe kó wọn nínú igbó ní Ọ̀yọ́ Àjàká fún àwọn Ọ̀yọ́mèsì nígbà tí ó ń gbà wọ́n lálejò ọrọọrún bí í ti máa á ṣe ní ìgbẹ́jọ́ rẹ̀. Ológbìn-ín ni ó ṣe ètò, tí ó sì darí bí àwọn abirùn náà ṣe ṣèsínjẹ bí wọ́n ṣe kó wọn níbi tí wọ́n ti ń dẹ́rù ba àwọn ẹmẹ̀sẹ̀ ọba ní Ọ̀yọ́ Àjàká.
- Nígbàkúùgbà tí aláàfin bá sì fẹ́ tún dá àwọn àlejò rẹ̀ mìíràn lára yá àwọn aṣẹ̀sínjẹ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí náà ni ó máa ń lò. Olúgbẹ̀ẹ́ Àgan sì dára pọ̀ mọ́ àwọn aṣesínjẹ náà lẹ́yìnọ̀rẹyìn.
- Nípa àtinúdá Ológbìn-ín tí ó jẹ́ olùdarí eré ni wọn fi bẹ̀rẹ̀ sí gbé eré náà kiri lẹ́yìnọ̀rẹyìn, tí ó fi di ohun tí wọ́n ń ṣe láàrin ìlú yàtọ̀ sí ààfin. Wọ́n tún ń ṣe àwọn eré mìíràn nígbà tí ó yá.
- Aláràn-án-ọ̀rin ni Adédèjì sọ pé ó máa ń rán aṣọ eré fún wọn. Ọlọ́jọwọ̀n sì ni agbẹ́gilére àkọ́kọ́ tó máa ń gbẹ́ oríṣiríṣi ère tí wọ́n nílò láti fi ṣe ìsínjẹ.
- Lẹ́yìn ikú Ológbìn-ín, Ẹ̀sà Ògbín gba ipò rẹ̀, òun sì ni ó sọ eégún aláré di iṣẹ́ ṣíṣe ní pẹrẹu.

## 4. 3 Láméètọ́

- Adédèjì gbìyànjú nípa akitiyan ṣíṣe àrògún àtúntò ìtàn ìgbéǹde eégún aláré láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀. Ó to ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìtàn ìwáṣẹ̀ àti takọni-kayéfì papọ̀ láti ṣe èyí ni, ó sì ṣe àmúlò oríkì àti ẹsẹ ifá bí a ti sọ tẹ́lẹ̀.

- Gẹ́gẹ́ bí Babayẹmi (1980) àti Götrick (1984) ti tọ́ka sí i, àléébù tí ó hàn kedere jùlọ nínú iṣẹ́ rẹ̀ náà ni pé ó fún ìtàn ìwásẹ̀, takọni-kàyéfì láti inú ẹsẹ ifá àti oríkì tí ó lò ní ìtumọ̀ bí ẹni pé ohun tí ó ṣẹlẹ̀ lójú ayé gidi ni. Ìdí nìyí tí ó fi sọ ìtàn Olúgbẹ̀ẹ́ Àgan tó jẹ́ ìtàn ìwáṣẹ̀ látinú ẹṣe ifá pọ̀ mọ́ tàwọn akọni-kàyéẽfì mìíràn.
- Oríṣiríṣi ni àlàfo tí ó yọ sílẹ̀ láti ìdí àléébù yìí. Oríṣìí sì ni ìtakora tí ó jẹ jáde nínú iṣẹ́ rẹ̀ náà. Götrick (1984) ti tọ́ka sí àwọn àléébù náà ni kíkún. Babayẹmi (1980) náà kò fara mọ́ fífún àwọn ìtàn ìwásẹ̀ wọ̀nyí ní ìtumọ̀ bí ẹni pé ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi ni wọ́n. Babayẹmí ní tirẹ̀ sọ pé látinú ìrírí láwùjọ lápapọ̀ ni eégún ti dìdelẹ̀.
- Àkíyèsí ti wa ni pé, níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé àwọn tó bẹnu àtẹ́ lu iṣẹ́ Adédèjì yìí kò ti mú àbá ìtàn tàbí àlàyé mìíràn tó gún régé ju ti Adédèjì lọ wá, ti Adédèjì náà ni a ó ṣì gbára lé ná títí dìgbà tí a ó rí àlàyé mìíràn tó gún régé ju tirẹ̀ lọ nípa ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè eégún aláré.

## 5. 0 Ìsọníṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí,

- A ṣe àgbéyẹ̀wò oríṣiríṣi orúkọ tí àwọn onímọ̀ àti ará ìlú fi ń pe àwọn eégún aláré. A sọ pé orúkọ àbùkù ni alárìnjó tí àwọn ènìyàn ń pè wọ́n. A sì ṣe àlàyé pé gbogbo àwọn orúkọ náà (alárìnjó, agbégijó, apidan ati lábalà) kàn ń fòté lé apá kan tàbí méjì nínú ọnà ìṣeré/ ìgbérékalẹ̀ ni.
- A ṣe àgbéyẹ̀wò akitiyan Adédèjì (1969) lórí ìgbéǹde àtidàgbàsókè eégún aláré. A sọ pé ìtàn rẹ̀ náà jẹ́ oríṣìí àtòjọ ìtàn ìwáṣẹ̀ àti takọni-kàyéẽfì látinú ẹsẹ ifá àti oríkì.
- Bí ó tilẹ̀ jẹ pé a tọ́ka sí àléébù tí àwọn onímọ̀ kan kíyèsí nínú àlàyé Adédèjì pé ó fún ìtàn ìwáṣẹ̀ àti takọni –kàyéfì nítumọ̀ bí ẹni pé ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi lójú ayéni, síbẹ̀ níwọ̀n ìgbà tí kò ti sí àbá mìíràn tí ó dára ju tirẹ̀ lọ, tirẹ̀ yẹn náà ni a óṣì máa mú lò.

## 6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàkọsílẹ̀ orúkọ márùn-ún tí wọ́n fi máa ń pe àwọn agbéréká àbáláyé. Èwo ni ó kógo já jùlọ nínú wọn? Kín sì ni àwíjàre rẹ lórí èyí?
2. Tọpa ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè eégún aláré gẹ́gẹ́ bí Adédèjì (1969) ṣe fi hàn.
3. Ṣe àlàyé kíkún lórí ipa Aláàfi Abíipa nípa ìdìdelẹ̀ eégún aláré.

## 7. 0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adédèjì, J. A. 1969. 'The Alarinjo Theatre: The Study of a Yoruba Theatrical Art from its Early Beginnings to the Present Times', Àpilẹ̀kọ fún oyè ìjìnlẹ̀ gíga University of Ibadan, Ibadan.

Adédèjì, J. A. 1972. "The Origin and Form of the Yoruba Masque Theatre", *Cahier d'etudes Africaines*, 12:2, o.i. 254-276.

Adédèjì, J. A. 1978. "Alárìnjó: the Traditional Yoruba Travelling Theatre". In Ogunba O. àti Irele. A. *Theatre in Africa*. Ibadan University Press.

Babalọla, S. A. 1966. *Content and Form of Yorùbá Ìjálá*. Oxford University Press, Oxford.

Babayẹmi, S. O. 1980. *Egúngún Among Ọ̀yọ́ Yorùbá*. Ìbàdàn.

Beier, U. 1964. The Agbegijo Masquraders", *Nigeria Magazine*, No. 82: 189 – 199

Götrick, I. 1984. Apidán *Theatre and Modern Drama: A Study in a Traditional Yorùbá Theatre, Its Influence on Modern Drama by Yorùbá Playwrights*. Almquist and Wiksell International. Armsterdam

Johnson, S. 1921. *The History of the Yoruba from the Earliest timeto the Beginning of the British Protectorate.* London, C. M. S.

Ògúndèjì, P. A. 2000. *Ritual as Theatre, Theatre as Ritual: The Nigerian Example*. Ìbàdàn: Ìbàdàn Cultural Studies Group.

# Ìpín 4: Ìṣeré Eégún Aláré

Àkóónú

1. 0 Ìfáárà

2. 0 Èròńgbà

3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú

4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4. 1. 0 Ìṣeré Eégún Aláré

4. 1. 1 Òṣèré

4. 1. 2 Ìgbáradì

4. 1. 3 ìgbésẹ̀ inú eré

5. 0 Ìsọníṣókí

6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7. 0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1. 0 Ìfáárà

A ti sọ nínú ìpín kẹta inú módù yìí, tí a ṣe gbẹ̀yìn pé àwọn eégún aláré náà ni Adédèjì (1969) pè ní alárìnjó. Orúkọ yìí jẹ́ orúkọ tí àwọn ará ìlú fi ń tàbùkù wọn. Ìdí nìyí tí àwa kò fi lo orúkọ náà; tí ó fi jẹ́ pé dípò bẹ́ẹ̀, a fara mọ́ lílo 'eégún aláré'; orúkọ tí àwọn eléré náà kúndùn láti máa fi pe ara wọn jù lọ. Síwájú sí i a ṣe àlàyé pé gbogbo àwọn orúkọ yòókù (apidán, alárìnjó, agbégijó, lábalà) tí wọ́n tún máa ń fi pè wọ́n ni kò kógo já gẹ́gẹ́ bí orúkọ gbogbogbòò, àyàfi 'eégún aláré' nìkan. A lè lo 'aré' tí ó wà nínú orúkọ 'eégún aláré' láti fi júwe gbogbo àwọn ọnà ìṣeré inú àré àwọn eléré náà lápapọ̀. Kò sí lára àwọn orúkọ yòókù tí ó ṣe é lò láti fijúwe gbogbo ọnà ìṣere yòókù bẹ́ẹ̀ lápapọ̀. Bákan náà ni a tún jíròrò lórí ìgbéǹde tàbí ìdìdelẹ̀ eégún aláré àti ìdàgbàsókè rẹ̀ nínu ìpín kẹta yẹn náà. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìpín kẹrin yìí, a ó jíròrò lórí ọ̀wọ́ àwọn òṣèré, ìgbáradì àti ìgbésẹ̀ inú ìṣeré àwọn aláré náà.

## 2. 0 Èròńgbà

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìwọ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ yóó ti le

- Ṣàlàyé nípa oríṣi ọ̀wọ́ àwọn òṣèré tí í máa ṣe eégún aláré.
- Sọ àwọn ojúṣe ọ̀wọ́ àwọn òṣèré kọ̀ọ̀kan.
- Ṣàlàyé bí àwọn eégún aláré ṣe máà ń gbáradì fún ìṣeré.
- Jírọ̀rò lórí àwọn ìgbésẹ̀ inú eré/idán eégún aláré.

## 3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú

1. Dárúkọ méjì tí o mọ̀ lára ọ̀wọ́ àwọn òṣèré eégún aláré.
2. Báwo ni àwọn eégún aláré ṣe máa ń ṣe ìpolongo ìṣeré wọn?
3. Ìgbésẹ̀ mélòó ni o lérò pé ó wà nínú ìṣeré eégún aláré?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1. 0 Ìṣeré Eré Eégún Aláré

Àwọn akópa nínú ìṣeré ni òṣeréipa yòówù kí irú ẹni bẹ̀ẹ̀ máa kó. Ó lè jẹ́ aṣèsínjẹ, onílù, oníjó, apohùn abbl. Ọ̀wọ́ mẹ́rin ni a pín wọn sí fún ìrọ̀rùn àgbéyẹ̀wò inú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wa ní ìhín. Kí á tó lọ sórí ìjírọ̀rò nípa ìṣeré gan-an a óò jírọ̀rò lórí bí àwọn aláré náà ti máa ń gbáradì fún ìṣeré wọn. Lẹ́yìn náà ni a óò jírọ̀rò lórí àwọn ìgbésẹ̀ mẹ́ta tí a pín ìṣeré wọn sí.

#### 4. 1. 1. Òṣèré

- Ó yẹ kí á sọ ọ́ ní ìbẹ̀rẹ̀ abala ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí wí pé iṣẹ́ ìran ni eré eégún aláré. ọ̀jẹ̀ ni a máa ń pe àwọn ìran yìí ní ilẹ̀ Yorubá Èyí fi hàn pé àjẹbí ni eré náà. Kì í ṣe pé àwọn tó jẹ́ ará ìta náà kì í sí lára àwọn ọmọ ẹgbẹ́ òṣèré eégún aláré, bí a ṣe rí àwọn abílọ́jẹ̀ tó jẹ́ ọmọ eléégún náà la ní àwọn ọ̀jẹ́wùmí, tó jẹ́ pé ará ìta ni wọ́n ṣùgbọ́n tí ìṣeré eégún aláré wù, tí àwọn náà sì dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ eégún aláré láti kọ́ iṣẹ́ náà.
- Ọ̀wọ́ mẹ́rin tí a pín àwọn òṣèré eégún aláré sí fún ìrọ̀rùn ìkẹ́kọ̀ọ́ wa ni:
    i. Onílù (onílù bàtá)
    ii. Olórin (pẹ̀lú apèsà )
    iii. Olókìtì (àti oníjó)
    iv. Apidán (aṣèsíjẹ)

- Ìlù bàtá ni àwọn eléégún aláré máa ń jó. Láàárín àwọn òṣèré eégún aláré, àwọn oníbàtá nìkan ni kì í ṣọmọ ẹgbẹ́ eégún aláre gan-an. Iṣẹ́ ìdílé ni iṣẹ́ Àyàn láàyè tirẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ àwọn eégún aláré náà ṣe jẹ́ iṣẹ́ ìdílé ni ìlù lílù náà jẹ́ iṣẹ́ ìdílé.
- Àwọn àyàn wọ̀nyí máa ń ní ìbáṣepọ̀ ọlọ́jọ́ pípẹ́ pẹ̀lú ẹgbẹ́ eégún aláré kan. Ẹgbẹ́ eléégún aláré kọ̀ọ̀kan níí máa ní onílù tí í máa bá a ṣeré. Àwọn àyàn tí ó máa ń lù fún ẹgbẹ́ eégún aláré tí máa ń mọ ohun tó ṣe kókó nípa ẹgbẹ́ eégún aláré tí wọn ń lù fún. Wọ́n sì ti máa ń mọ ìtàn ìran àti àṣírí eré ẹgbẹ́ eégún aláré náà dáradára. Ìdí nìyí tí kì í fi bẹ́ẹ̀ sí èdè àìyedè láàárín wọn. Bí aáwọ̀ kan bá wà, wọ́n máa ń pe ara wọn parí rẹ̀ ni, wọn yóò sì jẹ́ kó parí sí ibi tí wọ́n sọ ọ́ sí.
- Bí àwọn ẹgbẹ́ eégún aláré bá lọ sí òde, tí wọ́n sì gba ẹ̀bùn owó, aṣọ àti àwọn ohun mìíràn, ọ̀nà méjì lọ́gbọọgba ni wọn yóó pín in sí, ọ̀kan fún ọ̀wọ́ eégún aláré, ọ̀kan yòókù fún àwọn onílù. Àwọn eégún aláré a máa ṣe àwọn onílù wọn dáradára torí àṣepọ̀ ọlọ́jọ́ pípẹ́ tó ti wà láàárín wọn àti àṣírí idán/ eré wọn tí wọ́n ti mọ̀.
- Púpọ̀ nínú àwọn olórin/ apẹ̀ṣà (elégbè) ni ó máa ń jẹ́ ìyàwó, ọmọbìnrin tàbí ẹbí olórí ẹgbẹ́ eégún aláré. Àwọn wọ̀nyí ni wọ́n máa ń pẹ̀ṣà, tí wọ́n máa ń dárin, tí wọ́n sì máa ń gbe orin bí ó bá kan orin kíkọ. Àwọn ọkùnrin, yálà wọ́n ru ẹ̀kú tàbí wọn kò ru ẹ̀kú náà le pẹ̀ṣà, kí wọ́n dárin, kí wọ́n sì gberin tí òṣèré mìíràn dá. Ojúṣe àwọn olórin ni láti pẹ̀ṣà ní ìbámu pẹ̀lú idán tó ń lọ lọ́wọ́, láti dárin ní àkókò tó yẹ àti láti gbe orin tí a dá. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọkùnrin le jẹ́ olórin, àwọn obìnrin ni ó wọ́pọ̀ jùlọ nínú ọ̀wọ́ àwọn òṣèré eégún aláré yìí.
- Àwọn ọkùnrin nìkan ni í máa á tàkìtì ní àkókò ìṣeré. Bí ẹni tí ó ru ẹ̀kú, tí à ń pè ní òkolonbo/ jẹ̀pẹ́/ olókìtì (èyí ni àwọ̀tẹ́lẹ̀ tí ó bo gbogbo ara) ti lè tàkìtì náà ni ẹni tí kò ru ẹ̀kú nínú àwọn ọmọ ẹgbẹ́ eléégún aláré náà le tàkìtì. Obìnrin tí ó ní ìmọ̀ọ̀ṣe nínú òkìtì náà le ta á ṣùgbọ́n kò gbọdọ̀ ru ẹ̀kú ṣe èyí. Irúfẹ́ òṣèrébìnrin báyìí kì í wọ́pọ̀ rárá. Èèwọ̀ sì ni ẹ̀kú rírù fún obìnrin nínú awo eégún.
- Àwọn ọkùnrin nìkan ni wọ́n máa ń pidán. Apidán sì gbọdọ̀ ru ẹ̀kú. Ẹni tí kò bá ru ẹ̀kú kò lè pidán rárá. Apidán le jẹ́ ọmọdé, ó sì le jẹ́ àgbàlagbà. Apidán ẹyọ kan lè dá idán pa; méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ sì le jìjọ pa idán ẹyọ kan ṣoṣo.
- Àwọn apidán nílò láti wọ aṣọ eré mìíràn tó bá idán tí wọ́n ń pa mu lásìkò idán pípa.

- Àwọn idán tí kò le púpọ̀ ni ọ̀jẹ̀ wẹ́wẹ́ apidán lè pa, bí idán bá ti lágbára, àgbà ọ̀jẹ̀ ní í pa á. Kódà àwọn idán kan wà tí ó jẹ́ pé olórí ẹgbẹ́ òṣèré nìkan ló máa ń pa á.
- Àwọn apidán náà a máa pẹ̀ṣà tàbí kí wọ́n dá orin tó bá idán tí wọn ń pa lọ́wọ́ mu.
- Òṣèré kan ṣoṣo lè kó ipa tó ju ẹyọ kan lọ, ó le kópa méjì tàbí mẹ́ta papọ̀ lẹ́ẹ̀kan náà. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, apidán le ta òkìtì, ó le pẹ̀ṣà, ó sì le pa idán. Ó yẹ kí ó jọni lójú bí àwọn òṣèré eégún aláré ṣe le kó ipa púpọ̀ báyìí. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà láti kékeré, ní bí ọmọ ọdún mẹ́ta sí mẹ́rin ni ìkọ́ni ní iṣẹ́ eré eégún aláré ti máa ń bẹ̀rẹ̀. Ẹ̀kọ́ nípa ìlù lílù tí kì í ṣe ara iṣẹ́ eégún aláré nìkan ni wọ́n kì í kọ́ ni àkókò ìkọ́ṣẹ́. Gbogbo ọ̀nà ìṣeré yòókù ni wọ́n máa ń kọ́. Ìdí nìyí tí ó fi ṣe é ṣe fún òṣèré kan ṣoṣo láti lè kó ju ẹyọ ipa kan lọ ní àkókò ìṣeré.
- Bí ọmọ ìdílé eléégún aláré (ọ̀jẹ́dìran/ abílọ́jẹ̀) tí lè kọ́ iṣẹ́ náà ni ará ìta (ọ̀jẹ́wùmí) náà lè kọ́ iṣẹ́.
- Kò sí pé àkókò kan pàtó ni ìgbòmìnira gbọ́dọ̀ wáyé. Gbogbo rẹ̀ dúró lórí bí ọmọ ìkọ́ṣẹ́ náà bá ṣe já fáfá sí. Ṣùgbọ́n bí ẹni tí ó ti dàgbà díẹ̀ bá lọ kọ́ iṣẹ́ náà ó lè lò tó bíi ọdún márùn-ún sí mẹ́fà tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ.
- Bí ẹ̀kọ́ṣẹ́ eégún aláré ṣe rí náà ni ẹ̀kọ́ṣẹ́ ìlù náà ṣe rí. Láti kékeré jòjòló ni àwọn àyàn ti ń kọ́ ọmọ wọn ní ìlù, láti ibi omele bàtá ṣíṣán ni wọ́n ti máa ń bẹ̀rẹ̀. Díẹ̀díẹ̀ ni ọmọdé yóó máa lu ìlù tẹ̀ lé àwọn baba rẹ̀, tí yóò sì máa kọ́ nípa oríkì títí tí yóó fi di ọ̀tà nínú ìlù lílù.

4. 1. 2. Ìgbáradì

- Nípa dídánrawò ní ìdákọ́nkọ́ fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni àwọn òṣèré eégún aláre ṣe máa ń ní ìmọ́-ọ̀n-ṣe. Ṣùgbọ́n kí irú ìdánrawò yìí tó kẹ́sẹjárí, àwọn onílù náà a máa kópa níbẹ̀. Gbogbo idán tí wọn yóò pa, òkìtì títa, ijó jíjó àti orin kíkọ pẹ̀lú ẹ̀ṣà pípè ni wọn yóò ti fi dánran wò pẹ̀lú àwọn onílù wọn daádá, òǹwòran kì í sí níbẹ̀ ní àkókò ìgbáradì àti ìfidánrawò náà.
- Agbéréká ni àwọn eléégún aláré. Wọ́n sì gbọdọ̀ ṣe gbogbo ètò nípa ìrìnàjò wọn sílẹ̀ dáradára, kí wọ́n tó jáde láti máa gbé eré wọn káàkiri.

- Yàtọ̀ sí ìpalẹ̀mọ́ àwọn ohun èlò ìṣeré lápapọ̀, olórí ẹgbẹ́ eléégún náà gbọ́dọ̀ ránṣẹ́ sí alágbààá ìletò/ abulé/ ìlú tí wọn ń lọ.
- Òpé ni wọ́n máa ń pe ẹni tí í máa lọ jẹ́ iṣẹ́ náà. Àrokò ni yóò sì mú lọ. Bí alágbààá náà bá ti gba àrokò yìí tí ó sì fara mọ́ wíwá ẹgbẹ́ eégún náà ni òun náà yóò ti bẹ̀rẹ̀ sí palẹ̀mọ́ láti gbà wọ́n lálejò torí pé ọ̀dọ̀ rẹ̀ ni wọn yóò dé sí.
- Bí ẹgbẹ́ eléégún náà bá ti wọ ìlú ni wọn yóò máa lùlù tí wọn ó máa kọrin tí wọn yóò sì máa tàkìtì bí wọ́n ti ń lọ sí ilé Alágbààá tí wọn yóò wọ̀ sí. Èyí sì ní í máa dúró bí ìpolongo àkọ́kọ́, tí gbogbo ìlú yóò fi mọ̀ pé àwọn eléré eegún ti wọ̀lú.
- Nígbà tí wọ́n bá sinmi tán, Alágbààá náà yóò mú wọn lọ sí ilé ọba tàbí baálẹ̀. Tìlùtìlù náà ni wọn yóò sì bá lọ láti lọ kí olórí àwùjọ náà kí wọ́n sì júbà bí ó ti tọ́. Ó máa ń tó ọjọ́ kejì tàbí jù bẹ́ẹ̀ kí wọ́n tó pàtẹ eré gan-an.

### 4. 1. 3 Ìgbésẹ̀ inú ìṣeré

- Ní ọjọ́ tí wọ́n ó bá ṣeré, torintìlù àti ijó ni wọn óò lọ sí ibi ti wọn yóò ti pagbo eré. Ìpolongo ìṣeré ni a lè kà èyí náà sí.
- Ibi ìṣeré tí wọn yóò pàtẹ eré sí le jẹ́ ojúde ọba tàbí tìjòyè, ó sì tún lè jẹ́ àárin gbùngbùn ìlú tàbí ojú-ọjà nígbà tí ọjà bá ti tú. Bí àwọn eégún aláré bá fẹ́ ṣeré, àwọn ìgbésẹ̀ inú eré wọn nìyí:
    1. Ìṣíde – ìjúbà, orin, ẹ̀sà, ijó àti òkìtì títa pẹ̀lú bàtá jíjá
    2. Eré-oníṣe náà – oríṣìíríṣìí idán
    3. Ìkádìí – idán àparelé
- Ìṣíde eré ní wọ́ fí ń bẹ̀rẹ̀ eré. Pàtàkì nínú àwọn ohun tí wọ́n ńṣe ní àkókò yìí ni ìjúbà. Ẹ̀ṣà pípè sì ni wọ́n fi í gbé kalẹ̀ níbààmu pẹ̀lú ìlànà ìpohùn àwọn eléégún. Orin, ilù bàtá lílù, ijó; ìyẹn bàtá jíjá, àti òkìtì títa ni wọ́n sì máa kádìí rẹ̀.
- Lẹ́yìn èyí ni idán tàbí eré-oníṣe yóò tó bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu tí àwọn eégún náà yóò máa ṣe ìsínjẹ onírúurú ẹ̀dá-ìtàn bíi ẹranko, òrìṣà àti àwọn ènìyàn gbogbo láwùjọ.
- Lẹ́yìn tí wọ́n bá ti pa oríṣìíríṣìí idán tán wọn máa ń fi idán àparelé kádìí gbogbo ètò ìṣeré wọn. Èyí ni kí wọ́n pa idán ìyàwó/ ìyálọ́mọ/ tọkọtìyàwó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ

## 5. 0 Ìsọníṣókí

- Ní inú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a jíròrò lórí àwọn òṣèré inú ẹgbẹ́ eégún aláré wọ̀nyí: onílù, olórin, olókìtì àti apidán.
- A ṣe àlàyé bí àwọn eégún aláré ṣe máa ń ṣe ìgbáradì wọn síwájú eré. Ọ̀nà méjì tí ìgbáradì pín sí ni ìfidánrawò àti ìpalẹ̀mọ́ fún ìṣeré
- A ṣàlàyé níppa ojúṣe Òpé máa ń kó nínú ìpalẹ̀mọ́ ètò ìgbéréká
- A sọ̀rọ̀ nípa ìpolongo eré, ẹni tí yóò gbà wọn lálejò ní àwùjọ tí wọ́n ti lọ ṣeréàti ibi ìṣeré wọn.
- Bákan náà ni a ṣe àlàyé lóorí àwọn ìgbésẹ̀ mẹ́ta wọ̀nyí tí a pín ìṣeré eégún aláré sí nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí: Ìṣíde, Eré-oníṣe náà àti Ìkádìí.

## 6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣe àlàyé bí àwọn eégún aláré ṣe máa ń gbáradì fún ìṣeré wọn ní kíkún.
2. Ọ̀wọ́ mẹ́lòó ni àwọn òṣèré eégún aláré pín sí, kín sì ni ipa ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn?
3. Ìgbésẹ̀ mélòó ni ìṣeré àwọn eléégún aláré ní pín sí, ṣe àlàyé àwọn ìgbésẹ̀ náà ní ṣókí.

## 7. 0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adédèjì, J. A. 1969. ‘The Alarinjo Theatre: The Study of a Yoruba Theatrical Art from its Early Beginnings to the Present Times’, Àpilẹ̀kọ fún oyè ìjìnlẹ̀ gíga, Yunifásítì Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Adédèjì, J. A. 1972. “The Origin and Form of the Yoruba Masque Theatre”, *Cahier d’etudes Africaines,* 12:2, o.i. 254-276.

Adédèjì, J. A. 1978. “Alárìnjó: The Traditional Yorùbá Travelling Theatre”, Ogunba, O. àti Irele, A. (Olóòtú) *Theatre in Africa.* Ibadan University Press, o. i. 27-54. Ó tún wà nínú Ogunbiyi, Y. (olótùú) 1981, *Drama and Theatre in Nigeria: A Critical Source Book,* Nigeria Magazine Publication, Lagos, o.i. 221-247.

Ògúndèjì, P. A. 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature. Ibadan:* Centre for External Studies, Yunifáítì Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Ògúndèjì, P. A. 1992. *Yorùbá Drama 1*, Centre for External Studies, Yunifáítì Ìbàdàn, Ìbàdàn.

## Ìpín 5: Oríṣìíríṣìí Eré Eégún Aláré

### Àkóónú

1. 0 Ìfáárà

2. 0 Èròńgbà Àti Àfojúsùn

3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú

4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4. 1 Oríṣìíríṣìí Eré Eégún Aláré

5. 0 Ìsọníṣókí

6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7. 0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1. 0 Ìfáárà

Ní inú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó kọjá, ìgbésẹ̀ inú ìṣeré àwọn eléégún aláré tí a sọ̀rọ̀ nípa wọn ni, Ìṣíde júbà, orin, ẹ̀sà, ijó àti òkìtì títa pẹ̀lú bàtá; Eré-oníṣe náà – oríṣìíríṣìí idán; Ìkádìí – idán àparelé. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìgbésẹ̀ kejì àti ìkẹta tó jẹ mọ́ idán pípa ni a óò jíròrò lé lórí. Àwọn ohun tí a óò ṣàlàyé nípa àwọn idán yìí ni ìpínsísọ̀rí àwọn eré/idán náà àti àpẹẹrẹ àwọn ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan. A ó tún jíròrò lórí idán àparelé.

### 2. 0 Èròńgbà Àti Àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìwọ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ yóó le ṣe àlàyé ìpínsísọ̀rí àwọn idán/eégún aláré. Wọn yóò le ṣe àlàyé bí wọ́n ṣe ń pa idán kọ̀ọ̀kan, wọn yóò sì le fi àpẹẹrẹ gbe ìdáhùn wọn slẹ́sẹ̀

### 3. 0 Ìbéèrè Ìṣáájú

1. Ṣe ìpínsísọ̀rí àwọn idán eégún aláré.
2. Ṣe àlàyé ní kíkún bí idán ajẹmẹ́ranko àti idán ajẹmábirùn ṣe jẹ́ idán ajẹmẹ́sìn.
3. Ṣe àlàyé idán àparelé àwọn eégún aláré.

## 4. 0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4. 1. 0 Orísìírísìí eré (idán) àwọn eléégún aláré

- Idán ni àwọn eléégún aláré máa ń fẹ́ kí àwọn òǹworan wọn gbàgbọ́ pé àwọn ń pa nígbà tí wọ́n bá ń ṣe orísìírísìí àwọn eré kékèké wọn lójú agbo eré. Nítorí náà gbogbo ọgbọ́n ìṣeré ìfohunpòótọ́ ni wọ́n máa ń mú lò.
- Àwọn eré wọn náà kì í sábà á ṣe ìgbékalẹ̀ àhunpọ̀ ìtàn gígùn. Bí ìṣeré wọ́n bá ní àhunpọ̀ ìtàn nínú, kìí gùn rárá. Ọ̀plọpọ̀ ìgbà ni ó jẹ́ pé ìfẹ̀dá-ìtàn-hàn ni ìṣeré wọn.
- Wọ́n le ṣàfihàn àwọn bíi òrìṣà Ṣàngó, Ọbàtálá, Ìgunnukó, Agẹmọ abbl. àti àwọn ẹranko bíi ọ̀nì, erè, ọ̀bọ, erin, ẹkùn àti abbl. Wọn a tún maáa ṣàfihàn àwọn àwọn ẹni-òrìṣà, bíi atiro, àfín, asuké, eléyín wanbọ, elétí ehoro, ẹlẹ̀rẹ̀kẹ́ dindi àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Wọ́n a máa ṣàfihàn òyìnbó, ọba, ìjòyè, jagunjagun, ọlọ́rọ̀, alágbe, aṣẹ́wó àti ọ̀falè. Wọ́n le pa idán ìyáwó àti ọkọ rẹ̀ tàbí ti ìyálọ́mọ.

### 4. 1. 1 Ìpínsísọ̀rí eré eégún aláré

- Bí a bá lo ìjẹmẹ́sìn – àìjẹmẹ́sìn gẹ́gẹ́ bí òdiwọ̀n, a lè pín gbogbo àwọn idán eléégún aláré sí ìsọ̀rí ńláńlá méjì. Àwọn wọ̀nyí ni idán ajẹmẹ́sìn àti idán aláìjẹmẹ́sìn tàbí ajẹmọ́ṣẹ̀lẹ̀-àwùjọ.
- A tún lè tún idán ajẹmẹ́sìn pín sí idán ajẹmórìṣà, ajẹméni-òrìṣà/ àkàndá-èdá àti ajẹméranko. Bí Adédèjì (1969) ti sọ ní ayé àtijọ́ ó ṣeé ṣe kí àwọn ẹranko tí àwọn eléégún aláre máa ń ṣèsínjẹ́ wọn jẹ́ àmì ìdílé/ẹbí, tàbí iran/ orílẹ̀ kọ̀ọ̀kan láàrin àwọn Yorùbá. Ìtọkasí àwọn ẹranko bẹ́ẹ̀ wà nínú àwọn oríkì orílẹ̀ nígbà tí a bá ń ki àwọn ìran náà ní "ọmọ ẹkùn", "ọmọ erin", "ọmọ ìyẹ̀rú ọ̀kín", "ọmọ erè lápà", abbl.
- Ìsọ̀rí márùn-ún ni a lè tún àwọn idán aláìjẹmẹ́sìn/ ajẹmọ́ṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ pín sí. Àwọn wọ̀nyí ni idán ajẹmájèjì (tàbí àlejò láwùjọ), idán ajẹmọ́wà-ìbàjẹ́ àwùjọ, idán ajẹmọ́ṣẹ̀lẹ̀ pàtàkì-pàtàkì, idán ajẹmọ́ìtàn-ṣẹ̀lẹ̀-gidi àti idán àparelé.

- Bí a kò bá fi ojú ẹni òrìṣà wo àwọn àkàndá ènìyàn tí àwọn eléégún ń sínjẹ nínú ìṣeré wọn, tí a kàn rí wọn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ọ̀tọ̀ láwùjọ (tàbí abirùn) a lè pín eré náà mọ́ eré aláìjẹmẹ́sìn/ ajẹmọ́ṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ. A jẹ́ pé ìsọ̀rí wẹ́wẹ́ méjì ni idán ajẹmẹ́sìn yóò wá ni ti aláìjẹ-mẹ́sìn yóò sì jẹ́ mẹ́fà.
- Idán àparelé tí ó ṣìkẹfà lábẹ́ idán aláijẹmẹ́sìn/ ajẹmọ́ṣẹ̀lẹ̀ awùjọ, máa ń jẹ́ idán ìyàwó, tọkọtìyàwó tàbí ìyá ọlọ́mọ. Ìdán ajẹmọ́yàwó tàbí ti ìyálọ́mọ yìí ni àwọn eégún aláré fí máa ń kádìí eré. Ìdí sì nìyí tí a fi pè é ní idán àparelé.

### 4. 1. 2. 0 Àpèjúwe Ìṣeré

Ohun kan tí a gbọ́dọ̀ tún tẹnu mọ́ níbí ni pé, apidán gbọ́dọ̀ da ẹ̀kú borí ní gbogbo ìgbà. Ẹ̀kú àwọ̀tẹ́lẹ̀ tí a mọ̀ sí òkolonbo/ jẹ̀pẹ́/ olókìtì máa ń wà lára apidán nígbà gbogbo. Lórí èyí ni yóò máa wọ àwọn aṣọ ère yòókù lé tí yóò sì máa ṣèsínjẹ rẹ̀ nìṣòó. Ẹ jẹ́ kí á mú àwọn eré/ idán yìí ní ọ̀kọ̀ọ̀kan

### 4. 1. 2. 1 Idán Ajẹmórìṣà

- Idán ajẹmórìṣà ni àwọn eégún aláré kọ́kọ́ máa ń pa ní ojú agbo eré. Ìbà fún àwọn òrìṣà náà ni a lè sọ pé idán yìí máa ń dúró fún. Olórí ẹgbẹ́ eléré ni ó máa ń sábà pidán náà, àdáṣe sì ni. Lárá àwọn òrìṣà tí wọ́n máa ń sáábà sínjẹ ni Ṣàngó, Ọbàtálá, Ẹ̀yọ̀, Agẹmọ.
- Bí àwọn eégún aláré bá fẹ́ pidán Ṣàngó, apidán yóò múra ní ìbámu pẹ̀lú bí adóṣù Ṣàngó ti í múra. Igi ni wọn fi máa ń gbẹ́ oṣù tí yóò gbé borí. Yóò wọ gbérí Ṣàngó, yóò sì sán yẹ̀rì àti wàbì Ṣàngó, yóó gbé labà (àpò) Ṣàngó kọ́pá, yóò mú ṣẹ̀ẹ̀rẹ̀ àti oṣé Ṣàngó dání yóò sì máa pidán lóríṣiríṣi láti fi hàn pé alágbára gẹ́gẹ́ bíi ti Ṣàngó ni òun. Ó lè máa ki iná bọ ẹnu gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ. Àwọn olórin yóò máa kọrin ki Ṣàngó, oníbàtá yóò sì máa ṣán bàtá fún lákọlákọ. Lára àwọn orin tí wọ́n le máa kọ ní àsìkò yìí nìyí ní ìsàlẹ̀ yìí:

  Orin: Ṣàngó dé o
  Orò ọkọ Ọya ò
  Agbéná gẹngẹ bèké lẹ́nu

4. 1. 2. 2 Idán Ajẹmẹ́ranko

- Oríṣìíríṣìí ni ẹranko tí àwọn eléégún aláré lè sínjẹ. Wọ́n lè di erè tàbí òjòlá, ọ̀nì, ẹkùn, erin, ọ̀bọ tàbí ẹyẹ bíi àgbìgbò. Aṣọ eré tí apidán máa wọ̀ àti ìbòjú tí yóò lò gbọ́dọ̀ bá ìrísí ẹranko tí wọ́n ń sínjẹ mu. Àdáṣe ẹyọ apidán kan ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn idán ajẹmẹ́ranko máa ń jẹ́. Ọ̀gá ẹgbẹ́ eléré náà ni ó sì máa ń ṣe àwọn tí ó le níbẹ̀ – bíi ti òjòlá àti ọ̀nì. Nígbà mìíràn tí wọ́n bá ń pidán ẹkùn, wọ́n lè ju adìẹ sí ẹkùn náà kí ẹkùn náà tí yóò máa bẹ́ kiri tí. Bí ó bá ti fẹ́ máa mú ẹran ni ẹran yóó máa bọ́. Èyí yóó ká ẹkùn lára, yóó túnbọ̀ múra sí ẹran ṣùgbọ́n ọwọ́ rẹ̀ kò níí bà á náà. Àwọn olórin yóó máa kọrin pé "ojú ẹkùn ń pọ́n", wọn yóò sì máa gbè é pé "ìrù ẹkùn ń le". Èyí ni wọn yóó máa ṣe títí tí ẹran yóò fi sá lọ ráúráú.

4. 1. 2. 3 Idán Ajẹ́mẹ́ni-òrìṣà

- Àwọn ẹni òrìṣà ni àwọn aláàbọ̀ ara, abirùn tàbí àkàndá ènìyàn. Wọn a sì tún máa pè wọ́n ni ẹni òrìṣà. Òrìṣà Ọbàtálá ni ìtàn ìwáṣẹ̀ fi yé wa pé ó dá wọn bẹ́ẹ̀ nígbà tí ó ń bá Ògún kẹ́gbẹ́ tí ó sì mẹmu yó. Ìdí nìyí tí Olódùmarè fi binú sí i tí ó sì fi rán Odùduwà láti lọ gba iṣẹ́ ìṣẹ̀dá àti ìṣètò ayé lọ́wọ́ rẹ̀.
- Lára àwọn abirùn tí àwọn eléré eégún aláré máa ń sábàá sínjẹ ni dìndìnrìn, ẹlẹ́ẹ̀kẹ́ dìǹdì, eléyín wàm̀bọ̀, elétí ehoro, abuké abbl. Ìlò gàrétà ṣe pàtàkì nínú ìsínjẹ àwọn idán yìí nítorí pé nípa àwọn ìbòjú tàbí gàrétà tí àṣèsínjẹ bá gbé bojú, ni àfihàn abirùn náà yóò ṣe hàn dáradára.
- Bí ó bá jẹ́ pé idán ẹlẹ́ẹ̀kẹ́ dìǹdì ni àwọn eégún aláré yóó pa, ìbòjú tí ó fi àbùdá ẹ̀ẹ̀kẹ́ títóbi dìǹdì hàn ni aṣèsínjẹ yóó gbé bojú. Yóó máa ṣe àfihàn ẹ̀ẹ̀kẹ́ náà, yóò sì máa jó káàkiri ojú agbo eré bíwọ́n ti ń lùlù tí wọ́n sì ń kọrin fún un. Àpẹẹrẹ orin tí wọ́n le máa kọ nìyí:

Lílé: Kò sómi lámù ń jẹ́ gúgúrú

Ègbè: Pàmù lẹ́ẹ̀kẹ́ ń jẹ gúgúrú

Ọ̀ṣèré yóó máa jó sí orin náà, yóó sì máa ṣe ìfihàn ẹ̀ẹ̀kẹ́ dìǹdì rẹ̀ láti dá àwọn òǹwòran rẹ̀ lára yá.

4. 1. 2. 4 Idán Ajẹmájèjì

- Ṣàṣà ni àwọn àjèjì tí ó wà ní àwùjọ tí àwọn aṣèsínjẹ eégún aláré kò lè sín jẹ. Àpẹẹrẹ irú àwọn àjèji bẹ́ẹ̀ ni Tápà, Hausa àti Òyìnbó. Ìbòjú tí aṣèsínjẹ bá gbé bojú pẹ̀lú aṣọ eré tí ó wọ̀ ni yóò fi irú àjèjì tí ó ń sínjẹ hàn. Irú orin àti ijó tí wọ́n bá fi gbé ìsínjẹ náà kalẹ̀ yóò tún jẹ́ kí ìsínjẹ àjèjì tí òṣèré ń sín jẹ túbọ̀ yéni sí i.
- Bí ó bá jẹ́ ìsínjẹ Tápá ni wọ́n fẹ́ ṣe, aṣèsínjẹ yóò gbé ìbòjú tí a kọ ilà Tápà sí bo ojú, yóò máa jó kiri ojú-agbo bí àwọn olórin àti onílù bá ti ń kọrin: “Tápà, Tápà, Ejinana bààbo” fún un.

4. 1. 2. 5 Idán Ajẹmọ́wà-ìbàjẹ́

- Awọn eléégún aláré tún máa ń ṣe ìsínjẹ eré-oníṣe kéékèèké mìíràn láti fi bu ẹnu àtẹ́ lu àwọn ìwà àìdára láwùjọ Yorùbá. Lára irú idán bẹ́ẹ̀ ni ti ọ̀falè ati aṣẹ́wó àti ọ̀mùtípara wà. Nínú idán aṣẹ́wó àti ọ̀falẹ̀, eégún tí yóó ṣe ìsínjẹ aṣẹ́wó ni yóò kọ́kọ́ bọ́ sí ojú agbo tí yóò sì máa dínjú tí yóò máa rèdí kiri, ó lè máa tún ìró rẹ̀ ró lẹ́ẹ̀mẹwàá. Láìpẹ́ ọ̀falè á wọ ojú agbo, yóò fún aṣẹ́wó lówó, ṣùgbọ́n tí ó bá di àkókò àtiṣeré ìfẹ́, aṣẹ́wó yóò takú pé òun kò ṣe mọ́ nítorí pé nǹkan ọkùnrin ọ̀falè tóbi jù. Òun náà yóò fi orin dá a lóhùn pẹ̀lú orin pé:

  Gbà tó ń gba pọ́nùnpọ́ùn
  Ta lo ké sí?
  O wá ń ṣe yéè yéè
  Okó tóbi

  Aṣẹ́wó náà yóò sì fi orin fèsì fún un pé:

  Má rí mi fín o
  Má rí mi fín
  Èmi è é ṣẹgbẹ́ ìyáà rẹ
  Má rí mi fín

  Àwọn méjèèjì yóò bẹ̀rẹ̀ sí í wọ̀dìmú títí ọlọ́pàá yóò fi wá mú wọn lọ àtìmọ́lé. Bí wọ́n ti ń kó wọn jáde kúrò ní ojú agbo ni àwọn onílù àti olórin yóò máa kọrin pé:

  Wèré wèré gbòde
  Bí ti ń ṣakọ
  Bẹ́ẹ̀ ní ń ṣabo
  Bẹ́ẹ̀ ní ń ṣèyàwó olósùn lẹ́sẹ̀
  Wèré wèré gbòde

- Nígbà mìíràn aṣẹ́wó àti ọ̀falè lè ṣe ìsínjẹ ìbára-ẹni-lòpọ̀, ṣùgbọ́n lẹ́yìn-ọ̀-rẹyìn ọ̀falè yóò kó àrùn lára aṣéwó náà.

4. 1. 2. 6 Idán ajẹmọ́ṣẹ̀lẹ̀ pàtàkì-pàtàkì

- Àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ pàtàkì-pàtàkì láwùjọ a máa lọ̀ọ̀rìn débí wí pé òkíkí rẹ̀ a má la gbogbo àwùjọ já. Àwọn eléégún aláré a máa ṣe ìsínjẹ irú àwọn ìẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ nínú ìṣeré wọn. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ eégún aláré kan tí ó ń jẹ́ Agbórákò ní òde Ọ̀yọ́ láyé àtijọ́ ṣe ìsínjẹ bí Kúdẹ́ẹ̀fù àti àwọn ìránṣẹ́ Aláàfin mìíràn ṣe máa ń fi ayé ni àwọn ará ìlú lára tí ó jẹ́ pé ayé ọba ni wọn á láwọn ń jẹ. Ọ̀kan nínú àwọn eégún náà múra bíi Kúdẹ́ẹ̀fù ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í fi pàṣán na gbogbo èrò ìwòran, ó tún lu òṣèré tí ó ṣèsínjẹ ọba níbi tí ó jókòó sí lápá kan níbẹ̀ náà. Gbogbo ènìyàn sì bẹ̀rẹ̀ sí í kọ háà háà pé "Kúdẹ́ẹ̀fù ẹrú ò mọba".
- Láméyítọ́ ohun tí ó ń sẹ̀lẹ̀ láwùjọ ni Agbórákò fi idán náà ṣe. Àwọn èrò òǹwòran ni wọ́n túmọ̀ idán náà. ìpèdè wọn ń tọ́ka sí i pé ọba ni àwọn ìránṣẹ́ rẹ̀ tí ń jayé ìjẹkújẹ náà ń ta ẹrẹ̀ sí lára.
- Bákan náà ni ẹgbẹ́ eégún aláré Ayélabọ̀lá ṣe ìsínjẹ tí ó fi èdè-àìyedè àárin Akíntọ̀lá àti Awólọ́wọ̀ hàn ní Abẹ́òkúta ní ọdún 1966 (Adédèjì 1969).
- Àpẹẹrẹ mìíràn tún ni idán Elésèé, Ọba Ìgbàjà, tí olóògbé Ọ̀jọ̀gbọ́n Akínwùmí Ìṣọ̀lá (2012) ṣe nínú àpilẹ̀kọ rẹ̀ kan. Elésèé jẹ́ ọba tó burú jọjọ. Àwọn eégún aláré ti ó ṣe ìsínjẹ rẹ̀ ti gbọ́ nípa èyí. Bí wọ́n ti pa gbogbo àwọn idán tó yẹ ní pípa tán, eégún kan tó jẹ́ òpìdán yíra padà, ó sì di Elésèé, ọba Ìgbàjà, toun ti kókó ìwájú orí rẹ̀. Ìlù sọ lójú agbo eré àwọn olórin sì ti orin bọ ẹnu, ó di:

  Mo dElésèé ò
  Mo dElésèé
  Ọba Ìgbàjà
  Mo dElésèé

  Ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀ ọba tí kò ṣe dáadáa ni ìseré náà jẹ́. A sì gbọ́ pé wọ́n ta eléégún aláré náà lójì wí pé ó ṣe àfojúdi sọ́ba.

#### 4. 1. 2. 7 Idán Ajẹmọ́tàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi

- Àwọn eléégún aláré a máa ṣe ìsínjẹ ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi tí ó ṣẹlẹ̀ lójú ayé rí nínú ìṣeré wọn. Àwọn eégún aláré le ṣe ìsínjẹ ìtàn ogun, ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ ìlú, ìtàn akọni káyééfì tí ó ṣẹlẹ̀ lójú ayé ní sáà tó ti kọjá, ṣùgbọ́n tí a ṣì lè tọ́ka sí pẹ̀lú àrídájú. Irú ìṣẹ̀lẹ̀ tí wọ́n máa ń ṣèsínjẹ rẹ̀ bẹ́ẹ̀ a máa jẹ́ má-nigbàgbé ní ìgbésí ayé àwọn ènìyàn àwùjọ. wọ́n le ṣe ìsínjẹ ìjà ìgboro kan tàbí ipa burúkú tàbí rere tí àwọn ènìyàn kan kó.
- Lára àwọn ìtàn máni-gbàgbé bẹ́ẹ̀ tí àwọn eégún aláré máa ń ṣe ìsínjẹ ìṣẹ̀lẹ̀ rẹ̀ ni ìtàn àwọn Àlátíńgà. Àwọn ẹlẹ́sìn àjòjì kan ni àwọn Alátìńgà. Àjẹ́ ni wọ́n máa ń mú kiri. Láti apa Idàhọ̀mì ni wọ́n ti wọ ilẹ̀ Yorùbá ní àkókò ìjọba ìmúnisìn. Gẹ́gẹ́ bí àwọn ìṣeré idan wọn yòókù tí a ti ṣàlàyé rẹ̀ ìmúra eégún tí ó ń ṣe ìsinjẹ náà yóò jọ ti alátìńgà. Wọn óò sì máa ṣe gẹ́lẹ́ bí àwọn májẹ̀ẹ́mjẹ̀ẹ́ náà ti ń ṣe. Wọn ó máa lu ìlù wọn tí wọ́n ń gbé ọ̀pá wọn kiri ojú agbo wọn óò sì máa ṣe ìsínjẹ mímú àjẹ́.
- Ní àkókò tí ó ṣaájú ìjọba ìmúnisìn àwọn jagunjagun Ìdàhọ̀mì a máa wa yọ àwọn ará ilẹ̀ Yorùbá tí wọ́n sún mọ́ wọn lẹ́nu, tí wọn a máakó wọn lógun. Gbogbo agbègbè Ẹ̀gbá àti Yewa (Ẹ̀gbádò tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀) ni àwọn jagunjagun Ìdàhọ̀mì ti ṣe ọṣẹ́ láyé ìgbà náà. Àwọn eléégún aláré ní àdùgbò náà a sì máa ṣe ìsínjẹ jagunjaun Ìdàhọ̀mì ní ìrántí àkókò náà. Bí apidán bá fẹ́ ṣèsínjẹ jagunjagun ìdàhọ̀mì, yóó gbé ìbòjú tó fi àbùdá àwọn jagunjagun Ìdàhọ̀mì hàn bojú. Yóó wọ aṣọ ogun, yóó gbé ìbọn lọ́wọ́, bí ó ṣe ń nàró ni yóó máa bẹ̀rẹ̀ bí ọdẹ tó ń ṣọ́ ẹranko tàbí jagunjagun tó ń ṣọ́ ọ̀tá tó fẹ́ ta níbọn. Bí ó ti ń ṣe èyí ni àwọn olórin yóó máa kọrin pé:

> Lílé: Bó bá dúró a yìnbọn
> Bó bá bẹ̀rẹ̀ a yìnbọn
> Ègbè: Ìdàhọ̀mì ọkùnrin

tàbí

> Lílé: Dahọmi kọ́ o
> Ègbè: Dahọmi ni

### 4. 1. 2. 8 Idán Àparelé

- Ìsínjẹ ìyàwó/ tọkọtìyàwó/ ìyá ọlọ́mọ ni idán àparelé máa ń jẹ́ ní ọ̀pọ̀ ìgbà. Bí ó bá jẹ́ idán tọkọtaya ni àwọn eégún aláré fẹ́ pa, wọ́n le pa idán tọkọ tìyàwó alárédè̩. Ò̩ṣèré kan ni yóó ṣe ọkọ, èkejì yóó ṣe ìyàwó, wọn yóò sì máa márédè kiri ojú agbo eré.
- Bí ó bá jẹ́ ìsínjẹ ìyálọ̀mọ ni wọ́n fẹ́ ṣe, eégún kan ni yóò múra bí obìnrin, yóò wé gèlè tó jíire, yóó wọ bùbá tó gbádùn, yóó sì ró ìró olówó iyebíye. Yóó gbé ọmọlángidi lọ́wọ́, èyí dúró fún ọmọ tuntun. Wọn yóó wọ aṣọ fún ọmọlángidi náà bí ìkókó. Egúngún yìí sì le pọn ọmọlángidi náà. Ìyálọ̀mọ yìí le jókòó, kí ó máa ṣèsínjẹ fífún ọmọ lọ́mú. Àwọn òǹwòran yóó sì máa fún un lówó gẹ́gẹ́ bí owó ọmọ. Nígbà tó bá yá yóó máa jó, àwọn olórin yóó sì máa kọ orin fún un pé:

  Ọmọ lèrè ọjà
  Ọmọ lèrè ọjà
  Èdùmàrè kó fún gbogbo wa lọ́mọ
  Ọmọ lèrè ọjà

  Ìmúra ìyàwó/ ìyálọ̀mọ yìí máa ń ná àwọn eléré náà lówó gan-an ju ti gbogbo àwọn idán yòókù lọ. Ìdí ni pé aṣọ àti àwọn ohun èlò ìṣeré olówó iyebíye ni wọ́n máa ń fi ṣe eré náà.
- Nígbà tí wọ́n bá ṣe eré yìí dé ààyè kan, tí wọ́n pawó tẹ́ ara wọn lọ́rùn, àwọn ọmọ ẹgbẹ́ eléré tí wọn ti bẹ̀rẹ̀ sí í palẹ̀mọ́, yóò bẹ̀rẹ̀ sí máa fi orin dágbére pé:

  Ó yá ká relé
  Ilé là ń lọ
  Ọ̀jẹ̀ kan ò ṣawoṣawo
  Kó gbàgbé ilé
- Bí àwọn tó ń palẹ̀ mọ́ bá ti kó gbogbo àwọn ohun ìṣeré wọn tán, àwọn òǹwòran kọ̀ọ̀kan ti wọ́n ti mọ̀ pé eré ti parí yóó ti máa yọsẹ̀ díẹ̀díẹ̀. Nígbà tó bá yá àwọn eléré náà pàápàá ó bẹ̀rẹ̀ sí í fi orin dágbéré pe:

  Àwa ń lọọ
  Ẹ má pá ò dágbére o
  Àwa ń lọọ
  Ẹ má pá ò dágbére o.

Tàbí pé:

Àwa ń lọ,
Ó dìgbà ó ṣe,

Ká má fikú yara wa,

Ká má fàrùn yara wa

Tijótijó ni àwọn eégún aláré máa ń padà sí ilé tí wọ́n wọ̀ sí tí àwọn èrò ìwòran tó ń bá wọn jó lọ ibi tí wọ́n wọ̀ sí yóó fi gba ilé wọn lọ.

## 5. 0 Ìsọníṣókí

Ní inú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ṣe

- ìpínsísọ̀rí àwọn idán eégún aláré nípa lílo òdiwọ̀n jíjẹmẹ́sìn-àìjẹmẹ́sìn,
- àlàyé àgbékalẹ̀ oríṣìíríṣìí eré àwọn eégún aláré pèlú àpẹẹrẹ.

A le fi àwòrán onígi ìsàlẹ̀ yìí ṣe ìsọniṣọ́kí ìpínsísọ̀rí tí a ṣe:




(A ṣe àmúlò Ogundèji 1992, 2001)

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

4. Ọ̀ṣùwọ̀n pàtàkì wo ni a lè lò fún ìpínsísọ̀rí àwọn idán/eré eégún aláré sísọ̀rí ńláńá?

5. Àwọn ìsọ̀rí ńlá àti ìsọ̀rí kékèké wo ni a ní bí a bá lo òṣùwọ̀n tí o dárúkọ náà láti fi pín idán eégún aláré?
6. Ṣe àlàyé méjì, pẹ̀lú àpẹẹrẹ nínú àwọn idán eégún aláré.

## 7. 0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adédèjì, J. A. 1969. The Alarinjo Theatre: The Study of a Yoruba Theatrical Art from its Early Beginnings to the Present Times, Àpilẹ̀kọ fún oyè ìjìnlẹ̀ gíga University of Ibadan, Ibadan.

Adédèjì, J. A. 1972. "The Origin and Form of the Yoruba Masque Theatre", *Cahier d'etudes Africaines,* 12:2, o.i. 254-276.

Adédèjì, J. A. 1978. "Alarinjo: The Traditional Yorùbá Travelling Theatre", Ogunba, O. àti Irele, A. (Olóòtú) *Theatre in Africa.* Ìbàdàn University Press, o.i. 27 – 54. Ó tún wà nínú Ògúnbìyi, Y. (olótùú) 1981, *Drama and Theatre in Nigeria: A Critical Source Book,* Nigeria Magazine Publication, Lagos, o. i. 221-247.

Ìṣọ̀lá, A. 2012. *Òrìṣà Wo Ló Ń Gun Àwọn Òǹkọ̀wé Yorùbá,* DB Martoy, Ibadan.

Ògúndèjì, P.A. 1991. *Introduction to Yorùbá Oral Literature. Ibadan:* Centre for External Studies, Yunifasiti Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Ogundeji, P. A. 1992. *Yorùbá Drama 1(Eré-oníṣe Yorùbá 1*). Ibadan: Centre for External Studies, University of Ibadan, Ibadan.

Ògúndèjì, P. A. 2000. *Ritual as Theatre, Theatre as Ritual: The Nigerian Example*. Ìbàdàn Cultural Studies Group, Ìbàdàn.

Ogundeji, P. A. 2001. "Eré-oníṣe Yorùbá" nínú Bádé Àjàyí, (olóòtú) *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Ẹ̀dá-èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà Yorùbá*: *Ẹ̀dá-èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*, Ẹka Ìmọ̀ Ẹ̀dá-Èdè àti Èdè Afííríkà Yunifásítì Ìlọrin, Ìlọrin. o. i. 167-188.

MÓDÙ 3

ERÉ-ONÍṢE ÒDE ÒNÍ

Ìpín 1: Eré onílànà Ogunde: Orúkọ, ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè

1. 0 Ìfáàrà

2. 0 Èròǹgbà

3. 0 Ìbéèrè ìṣaájú

4. 0 Àkóónú iṣẹ́

4. 1. 0 Orúkọ

4. 1. 1 "Folk opera" (Eré Ìbílẹ̀ oníjó-lórin)

4. 1. 2 "Popular theatre" (Tíátà Mùtúmùwà)

4. 1. 3 "Travelling or itinerant theatre" (Tíátà agbéréká)

4. 1. 4 "Modern, contemporary or modern traditional theatre" (Tíátà òde-òní, bágbàmu tàbí tòde-òní mọ́ tàbáláyé)

4. 1. 5 "Professional itinerant theatre (Tíátà ajẹmọ́ṣẹ́-àmúṣe)

4. 1. 6 "Ogunde dramatic tradition and movement" (Eré-oníṣe onílànà Ogunde àti àjọ òṣèré rẹ̀)

4. 2. 0 Ìgbéǹde àti Ìdàgbàsókè

4. 2. 1 Akitiyan tí ó ṣaájú ti Ogunde

4. 2. 2 Àkókò Oníjólórin (1944 – 1950)

4. 2. 3 Àkókò Kọ́ǹsáàtì (1950 – 1965)

4. 2. 4 Àkókò Bágbàmu (1965 – títí di òní)

5. 0 Ìsọníṣókí

6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7. 0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1. 0 Ìfáárà

Oríṣìíríṣìí orúkọ tí àwọn onímọ̀ ti fi perí irúfẹ́ eré-oníṣe tí ọ̀rọ̀ kàn ni a fẹ́ gbé yẹ̀wò níbí. Ìlànà òdiwọ̀n tí a óò mú lò fún àgbéyẹ̀wò orúkọ wọ̀nyí ni ti ìpààlà tàbí ìṣeyàtọ̀. Ìyẹn ni pé orúkọ tí yó bá péye tàbí tí ó pegedé gbọ́dọ̀ lè pààlà ketekete sí tàbí kí ó fi ìyàtọ̀ gédégédé hàn ní ààrín ọ̀wọ́ àwọn eré oníṣe tí à ń gbé yẹ̀wò náà àti oríṣi àwọn eré oníṣe Yorùbá mìíràn. Èyí ni yóò jẹ́ kí á le dá eré tí a fẹ́ jíròrò lélórí náà mọ̀ yàtọ̀ sí àwọn oríṣiríṣi eré-oníṣe Yorùbá yòókù dáradára.

## 2. 0 Èròǹgbà

Ní ìparí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìnú ìpín kìn-ín-ní Módù kẹta yìí, ìwọ bí akẹ́kọ̀ọ́ yóó ti le ṣe

- Ìdámọ̀ àwọn orúkọ tí àwọn onímọ̀ ti fi pe irúfẹ́ eré-oníṣe tí Ogunde ṣe agbátẹrù rẹ̀.
- Àlàyé ohun tó mú púpọ̀ àwọn orúkọ náà kùnà.
- Àlàyé orúkọ tó tọ̀nà jùlọ láti fi pe àwọn eré náà.
- Àlàyé lórí ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè irúfẹ́ eré náà láti ìgbà tó ti bẹ̀rẹ̀ títí di lọ́ọ̀lọ́ yìí.

## 3. 0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Sọ ìtumọ̀ tíátà mùtúmùwà
2. Ta ni ó lo orúkọ “Tíátà òde òní mọ́ tàbáláyé,” kí sì ni ìdí rẹ̀?
3. Ṣe àkọsílẹ̀ orúkọ àwọn onímọ̀ mẹ́ta àti orúkọ tí wọ́n dábàá kí á máa fi pe irúfẹ́ eré oníṣe òde òní tí Ogunde fi lọ́lẹ̀.

## 4. 0. Àkóónú iṣẹ́

### 4. 1. 0 Orúkọ

Àwọn orúkọ tí a óò jíròrò lé lórí, tí àwọn onímọ̀ ti lò láti fi pe àwọn eléré tí a fẹ́ gbé yẹ̀ wò ni *Popular travelling theatre,* (Tíátà Mùtúmùwà); *Modern travelling theatre,* (Tíátà agbéréká òde-òni); *Contemporary travelling theatre,* (Tíátà agbéréká bágbàmu); *Modern traditional theatre,* (Tíátà òde òní mọ́ tàbáláyé) àti *Professional Itinerant theatre,* (Tíátà

àgbéréka ajẹmọ́ṣẹ́ Ṣíṣe). Ní ìsinsìnyí, a ó ṣe àgbéyẹ̀wò bí àwọn àwọn orúkọ náà ṣe kun ojú ìwọ̀n fún ìmúlò tó nípa gbígbé wọn lé orí ìlànà òdiwọ̀n tí a ti là sílẹ̀ nínú ìfáárà wa.

### 4. 1. 1 Eré ìbílẹ̀ oníjó-lórin (*Folk opera*)

- Ohun méjì tí orúkọ yìí ń fòté lé ni pé àwọn eré náà ní orin àti ijó nínú rẹpẹtẹ àti pé ó tún jẹ́ ti abínibí ìbílẹ̀ àwa Yorùbá. A kò lè yọ ti ìlù lílù náà sẹ́yìn níbi tí a bá ti dárúkọ orin àti ijó.
- Beier (1954) ni ó kọ́kọ́ lo orúkọ yìí nínú iṣẹ́ akadá, ṣùgbọ́n Beier pàápàá sọ pé orúkọ tí àwọn eléré fúnra wọn ń pe eré wọn ni òun mú lò, òun kọ́ ni òun dábàá orúkọ náà.
- Bí a bá gbé orúkọ yìí lé orí òṣùwọ̀n ìpààlà/ ìṣèyàtọ̀ tí a là kalẹ̀, kò múná dóko. Ìdí ni pé àwọn eré oníṣe Yorùbá yòókù, bíi ti àbáláyé tí a ti gbé yẹ̀ wò àti tàpilẹ̀kọ náà máa ń ṣe àmúlò orin, ìlù àti ijó bíi ti èyí tí à ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí náà. Nítorí ìdí èyí a rí i pé jíjẹmọ́ orin, ijó àti ìlù kì í ṣe àbùdá apààlà tàbí aṣèyàtọ̀ láàrin gbogbo àwọn eré-oníṣe Yorùbá rárárárá.
- Síwájú sí i, àwọn èròjà àti àkóónú eré-oníṣe tí à sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí kò jẹ mọ́ tìbílẹ̀ nìkan gẹ́gẹ́ bí Clark (1979) ṣe tọ́ka sí i; bí a ti rí tìbílẹ̀ níbẹ̀ náà la rí ti òde òní. Àwọn irúfẹ́ eré-oníṣe Yorùbá bí i ti àbáláyé àti ti àpilẹ̀kọ náà a sì máa ṣàmúlò àwọn èròjà àti àkóónú àṣà àbínibi ìbílẹ̀ Yorùbá náà; kì í ṣe irúfẹ́ eré yìí nìkan ni eré ìbílẹ̀ nígbà náà. Ìlò ìbílẹ̀ láti fi tọ́ka sí eré náà kò ṣe iṣẹ́ ìpààlà rárá nìyẹn.
- Ní àfikún, àwọn ọmọ ìbílẹ̀ Yorùbá ni olùṣẹ̀dá àti olùwòran àkọ́kọ́ àwọn irúfẹ́ eré Yorùbá yòókù àti ti èyí tí Ogúnde ṣagbátẹrù rẹ̀. Orí ìgbésí ayé àwọn ọmọ ìbílẹ̀ Yorùbá náà sì ni gbogbo wọn dá lé. Èyí fi hàn pé eré ìbílẹ̀ Yorùbá ni gbogbo wọn jọ jẹ́ pátápátá. Nítorí ìdí tí a mẹnu bà tán lókè nísinyìí gẹ́gẹ́ bí a ti sọ àti èyí tí a sọ ní ìhín, ó hàn gbangba pé ọ̀rọ̀ jíjẹ́ ti ìbílẹ̀ pa gbogbo àwọn eré Yorùbá náà pọ̀; kò pààlà tàbí kí ó fìyàtọ̀ hàn láàrin wọn.
- Yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀ ti àìpààlà, àkókò tí wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe irúfẹ́ eré bẹ́ẹ̀ nìkan ni a lè fi gbogbo ẹnu pè é ní oníjó-lórin; nígbà tó jẹ́ pé orin ìlù àtijó ni wọ́n fi ń gbé ọ̀pọ̀lọpọ̀

ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì inú àhunpọ̀ ìtàn eré bẹ́ẹ̀ kalẹ̀. Lẹ́yìn-ọ̀-rẹyìn, ọ̀rọ̀ sísọ ní pẹrẹu ni wọ́n ń ṣàmúlò fún ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì; orin, ìlù àti ijó ibẹ̀ kò wá tó nǹkan mọ́.

- Bí a bá tún lo òṣùwọ̀n àkókò tí eré-oníṣe yìí dìdelẹ̀ lááàrin àwọn Yorùbá, ọdún ìbílẹ̀ àti eégún aláré ló yẹ kí á pè ní eré ìbílẹ̀ gan-an, kì í ṣe tuntun tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ dé. Lẹ́yìn tí àwọn oyìnbó dé sáàrin wa ni eré tuntun yìí bẹ̀rẹ̀.
- Orí ìlànà ìṣeré ilẹ̀ òkèèrè tí a gbé eré yìí lé tún ta ko eré ìbílẹ̀ tí wọ́n fi ń pè é. Torí náà, a kò le gba orúkọ yìí wọlé rárá. Kò pààlà tàbí kí ó fi ìyàtọ̀ hàn lááárín rẹ̀ àti irúfẹ́ àwọn eré mìíràn.

### 4.1.2 Tíátà Mùtúmùwà (*Popular Theatre*)

- Orúkọ yìí ni ó ń tọ́ka sí i pé eré-oníṣe tí ó wà fún gbogbogbòò ni eré yìí jẹ́. Àpẹẹrẹ àwọn onímọ̀ tí wọn ṣàmúlò rẹ̀ ni Graham White, 1971; Ogunbiyi, 1981 àti Jeyifo, 1984.
- Ìdí tí orúkọ yìí kò fi le pààlà, kí ó sì ṣèyàtọ̀ lááàrin eré tí à ń gbé yẹ̀ wò àti àwọn eré-oníṣe Yorùbá yòókù ni pé àwọn eré àbáláyé Yorùbá (bíi ti eégún aláré àti tọdún ìbílẹ̀) náà wà fún mùtúmùwà; tọlọ́lá ti mẹ̀kúnnú, tàgbà tọmọdé; tọkùnrin tobìnrin, tọba tìjòyè àtaráàlú, tagbanisíṣẹ́, tòṣìṣẹ́ ni ó ń jẹ́ olùworan wọn.

### 4.1.3 Tíátà agbéréká (*Travelling or Itinerant Theatre*)

- Àbùdá pàtàkì tó ní í ṣe pẹ̀lú gbígbé eré káàkiri láti ibi kan dé ibi kejì, gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú ìjíròrò wa nípa eégún aláré, tí ó jẹ́ àbùdá kan gbòógì nínú eré-oníṣe náà ni orúkọ yìí ń tọ́ka sí. Lára àwọn onímọ̀ tí ó ṣàmúlò rẹ̀ ni Ogundeji, 1981; Jeyifo, 1981.
- Àbùdá ìgbéréká kò le fún wa ní orúkọ afìyàtọ̀-hàn tórí pé kì í ṣe irúfẹ́ eré tí à ń jíròrò lé lórí yìí nìkan ni a máa ń gbé ká gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú ìjíròrò wa nípa eégún aláré lókè.
- Àìlè fiyàtọ̀ hàn lááárín eré-oníṣe yìí àti ti eégún aláré ni orúkọ ajẹmọ́gbèéréká náà kò fi múná dóko tó bí èdè ìperí fún eré-oníṣe náà.

### 4.1.4 Tíátà òde-òní, Bágbàmu tàbí tÒde-òní mọ́ tÀbáláyé (*Modern, Contemporary or Modern Traditional Theatre*)

- Bóyá bí àwọn àbùdá eré-oníṣe àbáláyé àti eré-oníṣe tí à ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí ṣe ń yí wọnú ara wọn ló jẹ́ kí Ogunbiyi (1981) kan ọ̀rọ̀ aṣàpèjúwe (modern àti traditional) pọ̀ láti

fi perí eré-oníṣe náà. Láti tọ́ka sí bí wnọ́ ṣe ń ṣe ìmúlò fọ́n-ọ́n-rán tàbí àbùdá àbáláyé àti tòde òní papọ̀ nínú ìṣeré tuntun náà ló fi pè é ni tíátà òde-òní-mọ́-tàbáláyé.

- Àmúlò orúkọ "òde òní" àti ti "bágbàmu" láti fi pe eré-oníṣe tí à ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ kò fi ààlà tí ó wà láàárín irú eré-oníṣe bẹ́ẹ̀ àti àwọn eré-oníṣe àbáláyé hàn. Ìdí ni pé a ṣì ń ṣe àwọn eré-oníṣe tí a pè ní tàbáláyé wọ̀nyí náà lóde òní. Àbùdá tàbí fọ́n-ọ́n-rán àwọn méjèèjì ni ó ń yí wọnú ara wọn.
- Níwọ̀n ìgbà tí eré-oníṣe tí a pè ní tòde òní tàbí ti bágbàmu yìí ti ń ṣe àmúlò àkóónú àti ọgbọ́n ìṣeré ajẹmọ́ àbáláyé tí eré-oníṣe tí a kà sì ti àbáláyé náà sì ń ṣe àmúlò lára èròjà ìṣeré àkókò bágbà-mu tàbí tòde-òní, pípe irúfẹ́ eré tí à ń tọ́ka ní tòde òní tàbí ti bágbàmu, tàbí àkànpọ̀ méjèèjì yóò kù káàtó.
- Yàtọ̀ sí Ogunbiyi 1981,  Adédèjì (1978) àti Ògúndèjì (1981) ni àpẹẹrẹ àwọn onímọ̀ tí ó tún ti lo orúkọ náa rí nínú iṣẹ́ akadá wọn.

## 4. 1. 5 Tíátà ajẹmọ́ṣẹ́-àmúṣe (*Professional Theatre*)

- Bíọ́dún Jeyifo, 1981 ni ó lo orúkọ yìí láti ṣe àpèjúwe eré-oníṣe náà.
- Orúkọ yìí náà kùnà láti pààlà sí ààrín eré-oníṣe náà àti ti eégún aláré níwọ̀n bí ó ṣe jẹ́ pé iṣẹ́-àmúṣe ìran àwọn ọ̀jẹ̀ ni eégún aláré náà jẹ́; a lè lo orúkọ náà láti fi pe eégún aláré náà.
- Orúkọ yìí kò le fi ìyàtọ̀ hàn láàárín wọn àti eré-oníṣe tí à ń jíròrò nípa rẹ̀ yìí lópin ìgbà tó ti jẹ́ pé Ṣíṣe gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ òòjọ́ ni àwọn méjèèjì.

## 4.1.6 Eré-oníṣe onílànà Ogunde àti Àjọ òṣèré rẹ̀ (Ogunde *Dramatic Tradition and Movement*)

- Torí pé àwọn orúkọ wọ̀nyí kò pààlà láàárín irúfẹ́ eré-oníṣe tí à ń jíròrò lé àti àwọn eré Yorùbá mìíràn ni Ògúndèjì, 1987 àti 1988 ṣe dábàá pé kí á fi orúkọ Ogunde perí eré-oníṣe náà. Àwíjàrè rẹ̀ ni pé Ogunde ni ẹni tí ó jẹ́ olùlànà pàtàkì nídìí iṣẹ́ náà tí ogunlọ́gọ̀ àwon yòókù sì fi ṣe àwòkọ́ṣe.
- Àléébù tí àwọn kan tọ́ka sí nípa orúkọ yìí ni pé orúkọ ẹyọ ẹnìkan ṣoṣo ni Ògúndèjì lò nígbà tí ó jẹ́ pé ọ̀pọ̀ ni àwọn tí ó ń ṣàmúlò ìlànà náà. Ohun tí ìtàn fi yéni ni pé Ògúndé ni ó kọ́kọ́ sọ eré náà di iṣẹ́ Ṣíṣe tí ó sì dá ìgbéréká rẹ̀ sílẹ̀. Àwọn tí wọn ti ń ṣerú eré bẹ́ẹ̀ ṣáájú Ogunde kò gbé irú ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀. Nínú ìtàn ìbẹ̀rẹ̀ àti ìgbéǹde eré náà

gbogbo onímọ̀, àti àwọn eleré pàápàá, ló fẹnu kò pé Ogunde ni ó léwájú nínú àṣà ìṣeré náà.

- Àṣà lílo orúkọ olùlànà nǹkan láti fi pe ohun náà kì í ṣe ohun ọ̀tun rárá. A kò sì gbọdọ̀ gbàgbé pé ohun tí ó mú kí Ògúndèjì dábàá orúkọ yìí ni pé à ń wá orúkọ tí yóò fi ìyàtọ̀ hàn gedegbe láàárín eré-oníṣe yìí àti àwọn tí ó ti wà síwájú rẹ̀.

## 4. 2. 0 Ìgbéǹde àti Ìdàgbàsókè

Bí eré-oníṣe onílànà Ogunde ṣe bẹ̀rẹ̀ àti bí ó ṣe dàgbà sókè ni ìjíròrò inú abala ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí dá lé lórí. A pín ìjíròrò náà sí ìsọ̀rí mẹ́rin: Akitiyan tí ó sáájú ti Ogunde; àkókò oníjó-lórin, àkókò Kọ́ńsáàtì àti àkókò bágbàmu. Iṣẹ́ Ọ̀jọ̀gbọ́n Ẹ̀bùn aya Clark, (1979) ni olórí iṣẹ́ tí a fi ṣe àtẹ̀gùn ní ìhín.

## 4. 2. 1 Akitiyan tí ó ṣaájú ti Ogunde

- Láti Inú àṣà ìṣeré ìbílẹ̀ àti ti ilẹ̀ òkèèrè ni eré oníṣe onílànà Ogunde ti dìdelẹ̀. Àwọn ẹrú tí ó ti gba òmìnira tí wọ́n dé sí Èkó láti ilẹ̀ Sàró, Brazil àti Kúbà ni wọ́n kó àṣà ìṣeré òkè òkun yìí wọ Èkó. Eré tí wọ́n ṣe ní èdè Gẹ̀ẹ́sì ni ó wọ́pọ̀ nígbà náà. Ẹ̀yìnọ̀rẹyìn nígbà tí ọ̀rọ̀ kí á máa gbé àṣà ìbílẹ̀ lárugẹ ń gbilẹ̀ sí i ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí ṣe eré oníṣe ní èdè Yorùbá.
- “Sacred Cantata” àti “Native Air Opera” ni wọ́n ń pe irú eré-oníṣe lédè Yorùbá tí ó kọ́kọ́ gbilẹ̀ nígbà náà; orin kíkọ ni ó ṣe pàtàkì ju ìsínjẹ àti àwọn àbùdá eré-oníṣe yòókù lọ nínú irú àwọn ìṣeré náà.
- Alára àwọn alákitiyan tí ó ṣe pàtàkì nígbà náà ni J. A. Oyedele tí ó kọ eré ‘King Eléjìgbò and Princess Àbẹ̀jẹ́ of Kontangora’, èyí tí àwọn ẹgbẹ́ Ifẹ́ ṣe ní 1903; àṣeyọrí eré-onítàn náà la lérò pé ó tún jẹ́ kí Oyedele kọ òmíràn tí ó pè ní *The Jealous Queen Ọya of Ọ̀yọ́* tí àwọn ẹgbẹ́ Ifẹ́ kan náà ṣe ní ọdún 1905.
- Àkíyèsí tí ó yẹ kí á ṣe nípa àwọn eré méjèèjì yìí ni pé èdè Gẹ̀ẹ́sì ni wọ́n fi kọ àkọlé wọn bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé eré-onítàn ní èdè Yorùbá ni a pè wọ́n. Àṣà fífún eré Yorùbá ní àkọlé Gẹ̀ẹ́sì báyìí fara hàn nínú eré-oníṣe ti Ogunde gan-an alára títí di àkókò bágbàmu ní ọdún 1965.

- Ẹgbẹ́ Glee Singers tí ó ti máa ń ṣe eré ní èdè Gẹ̀ẹ́sì tẹ́lẹ̀ rí gbé ìkéde síta fún ìdíje ẹni tí ó bá lè kọ eré-onítàn tí ó dára lédè Yorùbá ní ọdún 1910. Eré Olympus Moore *Aṣìka Bí Àparò* àti ti I. B. Akínyẹlé *Àwọn Ìwàrẹ̀fà Mẹ́fà* ni ó gbégbá orókè nínú ìdíje náà, ṣùgbọ́n ti I. B. Akínyẹlé ni wọ́n lò.
- Lára àwọn eléré àkókò yìí mìíràn ni A. B. David, G. I. Onímọlẹ̀, A. A. Láyẹni, H. A. Olúfọye, P. A. Dáwódù àti T. E. K. Phillips.
- Ọdún 1944 ni a kọ́kọ́ gbúròó Ogunde nígbà tí ó ṣe eré onítàn *The Garden of Eden and the Throne of God.* Gbogbo ìrírí ìṣeré àbáláyé àti ti akókò bágbàmu ìgbà tirẹ̀ ni ó mú lò tí ó sì ṣe àfikún àwọn àtinúdá tí ó mú ìyípadà bá ìṣeré lákòókò náà.
- Ní ọdún 1946 ni Ogunde tó fi iṣẹ́ ọlọ́pàá tí ó ń ṣe sílẹ̀ láti gbájú mọ́ eré-oníṣe gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ àmúṣe tí ó bẹ̀rẹ̀ sí í gbéré rẹ̀ káàkiri. Òun ni bẹ̀rẹ̀ ìgbéré oníṣe òní ká.
- A. A. Láyẹni nìkan ni a gbọ́ pé òun náà fi eré-oníṣe ṣe ojúlówó iṣẹ́ lára àwọn tí wọ́n ń ṣe eré tẹ́lẹ̀. Àwòkóṣe Ogunde ni a lérò pé ó fún un ní ìwúrí.

### 4. 2. 2 Àkókò Oníjólórin (1944 – 1950)

- Eré oníjólórin tí ó fara pẹ́ ti “native air opera” àti “Sacred Cantata” nípa àmúlò orin ni ó gba àkókò yìí kan; ṣùgbọ́n irú orin tí Ogunde ń kọ yàtọ̀, ó sì dára ju ti àwọn aṣáájú rẹ̀ lọ.
- Lótìítọ́ ni pé púpọ̀ àwọn eré onítàn oníjólórin àkókò yìí ni ó jẹ́ ajẹmọ́tàn Bíbélì síbẹ̀ a rí àwọn tí ójẹ mọ́ ìtàn àti àṣà ìbíilẹ̀ Yorùbá àti ìṣẹ̀lú bágbà-mu àkókò náà. Orin inú wọn àti àwọn aṣọ eré pẹ̀lú àwọn àbùdá ìṣeré mìíràn mú àṣà abínibí lò dáradára; èyí sì ni ohun pàtàkì tí ó mú kí Ogunde ta àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ yọ nígbà náà.
- Bí Clark (1979) àti Adédèjì (1973) ti sọ lára àwọn tí ó gbé òṣùbà fún Ogunde nípa àtinúdá rẹ ni A.C. Jones nínú ìwé ìròyìn *Daily Service* ti ọjọ́ 29 oṣù kẹfà ọdún 1944.
- Ogunde ni ó kọ́kọ́ mú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àbùdá eré oníṣe eégún aláré lò nínú ìṣeré rẹ̀ ní àkókò yìí. Yàtọ̀ sí ìgbéré-ká tí a ti mẹ́nu bà, àwọn àpẹẹrẹ mìíràn ni ti ètò ìgbéré-kalẹ̀ lórí ìtàgé alábala mẹ́ta ti orin ìṣíde – eré-onítàn – orin ìparí, lílo òṣèrébìnrin, sísọ eré-oníṣe di iṣẹ́ ìdílé/ ẹbí abbl.

- Àpẹẹrẹ àwọn eré oníjólorin ajẹmọ̀tàn Bíbélì tí Ogunde ṣe lásìkò yìí ni *The Garden of Eden and the Throne of God, Israel in Egypt, Nebuchadnezzar's Reign* àti *King Solomon*.
- Àwọn eré oníjólórin ajẹmóṣèlú bágbà mu tó kọ nígbà yìí ni *Worse Than Crime, Strike and Hunger, Tigers Empire, Towards Liberty* àti *Bread and Bullet*.
- Tàwọn ajẹmọ́tàn àti áṣà ìbílẹ̀ ni *Journey to Hearen, Mr Devil's Money, Yours Forever* àti *Half and Half* (Clark 1979:110).
- Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọdún 1950 ni Ogunde ti jáwọ́ nínú kíkọ eré oníṣe oníjólórin tuntun, ọ̀pọ̀ ni àwọn tí ó ṣe àwòkọ́ṣe irú eré yìí kí ó tó di 1950 yẹn àti lẹ́yìn 1950 pàápàá. Àwọn kò sì tètè jáwọ́ nínú rẹ̀ lẹ́yìn tí Ogunde ti pa ìlànà náà tì. Kódà Ògúndé fúnra rẹ̀ a ṣì máa ṣe àwọn eré oníjólórin rẹ̀ tí ó jẹ́ gbajúgbajà fún àwọn òǹwòran rẹ̀ lẹ́yìn ọdún 1950 dáradára.
- Lára àwọn irú eléré tí wọ́n máa ń ṣe eré oníjólórin lẹ́yìn 1950 ni E bẹ́ẹ̀ ni ti Láyẹni, Onímọlẹ̀, Oyin Adéjọbí, Kọ́lá Ògúnmọ́lá àti Dúró Ladipọ.

4.2.3 Àkókò Kọ́ńsáàtì (1950 – 1965)

- Nígbà tí Ogunde gbé eré-onítàn *King Solomon* lọ sí ilẹ̀ Ghana ní 1948 kò rẹ́ni wò ó nítorí pé irú eré-onítàn bẹ́ẹ̀ kò gbajúmọ̀ ní ọ̀hún. Eré kọ́ńsáàtì, nínú èyí tí ọ̀rọ̀ sísọ àti àwàdà ti peléke ni ó wọ́pọ̀ níbẹ̀.
- Nítorí náà ní ọdún 1950 tí ó tún gbéré lọ sílẹ̀ Agànyìn, eré *Swing The Jazz* tí ó jẹ mọ́ ti ìlànà Kọ́ńsáàtì báyìí ni ó gbé lọ. Irú eré yìí fi ààyè sílẹ̀ fún ìbára-ẹni-sọ̀rọ̀ tààrà láàrin òṣèré àti òǹwòran ní àkókò ìṣeré. Ó sì tún fi ààyè gba kí òṣèré kọ̀ọ̀kan máa lo àtinúdá tirẹ̀ ní kíkún láti gbé ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì kalẹ̀ ni àkókò ìṣeré.
- Irú àwọn ààyè wọnyí kò sì nínú eré-onítàn oníjólórin níbi tí ó jẹ́ pé orin tí àwọn òṣèré ti kọ́ sórí ni wọn óò máa kọ ṣáá.
- Ní àkókò yìí náà ni àwàdà ṣíṣe nínú eré-onítàn kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ sí í fara hàn kedere nínú eré-oníṣe onílànà Ogunde.
- Moses Ọlaiya Adéjùmọ̀ ni ó tẹra mọ́ eré aláwàdà yìí ní ẹ̀yìn-ọ̀-rẹyìn tí ó sì sọ ọ́ di ẹ̀ka kan pàtàkì láàyè ara tirẹ̀ nínú eré-oníṣe onílànà Ogunde.

- Lára àwọn eléré tí ó tún kópa takuntakun nínú eré aláwàdà yìí ni Ọlá Ọmọnìtàn (Ajímájàsán), Ojó Ladipọ (Bàbá Mèró) àti àwọn Jekọbu, Pápà Lolò àti Adẹ́rùpọ̀kọ.
- Ní àkókò yìí kan náà ni ìlò èdè Gẹ̀ẹ́sì àti bòròkìnnì tún gbilẹ̀ nínú ìṣeré náà.
- Bórókìnnì yìí ni àwọn eléré náà máa ń lò nígbà tí wọ́n bá gbé eré lọ síbi tí wọn kò ti gbédè Yorùbá bí i ilẹ̀ Ibo, ilẹ̀ Hausa àti Ghana.
- Lára àwọn eré onítàn tí Ogunde ṣe ní àkókò yìí ni *Highway Eagle, My Darling Fatima, Portmanteau Woman, Princess Jaja, Village Hospital, Delicate Millionaire* àti *Song of Unity* (Clark 1979: 128).

### 4. 2. 4 Àkókò Bágbàmu (1965 síwájú)

- Lẹ́yìn ìgbòmìnira, tí gbígbé àṣà ilẹ̀ baba ẹni lárugẹ́ tún fẹsẹ̀ múlẹ̀ síwájú sí i nìdàgbàsókè tuntun tuntun ti bẹ̀rẹ̀ sí súyọ nínú eré onílànà Ogunde. Ní àkókò yìí ni Ogunde bẹ̀rẹ̀ sí ṣàmúlò àkọlé Yorùbá fún àwọn eré-onítàn rẹ̀.
- *Yorùbá Ronú* tí ó jẹ́ eré tuntun ní àkókò yìí ni Ogunde fi bẹ̀rẹ̀ ìlànà tuntun náà ni ọdún 1965. Lẹ́yìn náà, ó yí àkọlé *Journey to Heaven* sí *Ìbejì Méjì; The Black Forest* di *Igbó Irúnmalẹ̀; Mr Devil's Money* di *Àyìndé; Yours forever* di *Morẹ́nikẹ́; Half and Half* di *Sẹranko Ṣènìyàn; Village Hospital* di *Ilé Ìwòsàn; Delicate Millionaire* sì di *Olówó Òjijì*. Lára àwọn eré tuntun mìíràn tí ó ṣe ní àkókò yí ni *Àròpin N'tènìyàn, Awo Mímọ́, Àyànmọ́, Onímọ́tò, Màmá Èkó* àti *Ayé* (Wo Clark 1979 fún àlàyé kíkún.)
- Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìṣeré onílànà Ogunde ti bẹ̀rẹ̀ lórí rédíò ní ọdún 1945 nígbà tí eré oníjólórin Israel in Egypt di gbígbé-jádé lórí *Radio Re-difussion Servise* tÈkó (Clark, 1979:18). Nígbà tí yóò fi di 1958, bí Ogundeji (1981) ti sọ Oyin Adejọbí náà ti ń ṣeré lórí rédíò lÉkòó. Ṣùgbọ́n àkókò bágbamu ni ìṣeré lórí rédíò tó búrẹ́kẹ́.
- Bákan náà ni ọ̀rọ̀ rí fún ìṣeré lórí tẹlifíṣàn. Ogunde ló kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ eré ṣíṣe lórí ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán yìí ní àárín 1959 sí 1960 nigbà tí tẹlifíṣàn kọ́kọ́ dé. Lẹ́yìn ìgbòmìnira ni, Dúró Ladipọ àti àwọn eléré mìíràn bí Akin Ògúngbè, Kọ́lá Ògúmọ́lá náà bẹ̀rẹ̀ eré ṣíṣe lórí tẹlifíṣàn. Ọ̀wọ́ eré *Tíátà Yorùbá* nìkan ni eré Yorùbá tí wọn máa ń ṣe lọjọọjọ́ ẹtì fún ọgbọ̀n ìṣẹ́jú láàrín aago mẹ́jọ sí mẹ́jọ àbọ̀ nígbà náà.

- Nígbà tí àkókò bágbà-mu yóò fi bẹ̀rẹ̀ ní 1965, ìṣeré lórí tẹlifíṣàn náà ti di gbajúgbajà. Ọ̀dún 1965 yẹn gan-an ni Ilé iṣẹ́ Tẹlifíṣàn Ìwọ̀ Oòrùn Ilẹ̀ Nàìjíríà (WNTV, tí ó léwájú ní gbogbo Ilẹ̀ Afíríkà) bẹ̀rẹ̀ ètò ṣíṣàwárí àwọn òṣèré lédè abínibí nítorí wọ́n fẹ́ mú kí tẹlifíṣàn di ohun ìfigbáṣà abínibí lárúgẹ. Nípasẹ̀ ètò yìí ni wọn ṣe ṣàwárí Moses Ọláìyá Adéjùmọ̀ (Bàbá Sàlá), tí wọ́n sì tipa bẹ́ẹ̀ dá ọ̀wọ́ eré *Aláwàdà* sílẹ̀ ni 1965 yẹn. Ọjọọjọ́rùú ni wọn máa ń ṣe é láàrin aago méje sí méje àbọ̀. 1970 ni wọ́n ṣàwárí Ọlá Ọmọnìtàn (Ajímájàṣán) tí wọ́n sì dá ọ̀wọ́ eré *Àwàdà* sílẹ̀; ọjọọjọbọ ní àago méje sí méjé ààbọ̀ náà ni wọ́n máa ń ṣe é.
- Nígbà tí yóò fi di ọdún 1976 eré Yorùbá ṣíṣe lórí tẹlifíṣàn ti di ẹ̀ẹ̀marùn-ún lọ́sẹ̀ láàrin aago mẹ́jọ kùṣẹ́jú mẹ́ẹ̀dọ́gbọ̀n sí aago mẹ́jọ kọjá ìṣẹ́jú márùn-ún ni wọ́n ń ṣe wọ́n lójoojúmọ́. Eré kúúkùùkú tí àhunpọ̀ ìtàn wọn kò gùn lọ títí ni àwọn eré náà.
- Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ṣíṣeré aláhunpọ̀-ìtàn gígùn, oníwákàtí kan ti bẹ̀rẹ̀ láti 1974 pẹ̀lú eré *Èkùrọ́ Ọlọ́jà* (ti Oyin Adéjọbí) àti *Fẹrẹ bí Ẹkùn* (ti Adébáyọ̀ Fálétí); 1976, lẹ́yìn tí àkókò bágbàmu bẹ̀rẹ̀ ni eré aláhunpọ̀-ìtàn gígùn tó wasẹ̀ mọ́lẹ̀ pẹ̀lú eré gígùn ọlọ́sẹ̀ mẹ́tàlá *Igbó Irúnmọlẹ̀* (ti Dúró Ladipọ̀). *Arélù*, eré Jímọ̀ Alíù (1986) aláhunpọ̀-ìtàn gígùn, tí wọ́n ṣe lórí tẹlifíṣàn Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ TSOS (nígbà náà ṣùgbọ́n tí ó ti di BCOS lónìí) ni ó sọ eré tẹlifíṣàn ọlọ́sẹ̀ mẹ́tàlá di gbajúgbajà. Lára àwọn irú eré bẹ́ẹ̀ tí ó wáyé lẹ́yìn náà ni *Ẹniìtàn, Adé Ọba, Awọ Ẹkùn, Yánpọnyánrin, Ìkà Lọmọ Ejò* àti *Ọmọ Inú Òkú* (wo Ògúndèjì, 2014: 36).
- Ìṣeré sórí àwo rẹ́kọ́ọ̀dù ti wà ṣaájú àkókò bágbàmu. Bí àpẹẹrẹ, Ogunde ti ń gbé àwọn orin eré rẹ̀ jáde sínú àwo rẹ́kọ́ọ̀dù ṣaájú ìgbomìnira. Lẹ́yìn ìgbòminira pàápàá ní àkókò bágbàmu tí à ọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí ni Institute of African studies ní Yunifásítì Ìbàdàn sì gbé àwọn eré Duro Ladipọ, *Ọba Kò So* àti *Ẹ̀dá* pẹ̀lú ti Kọ́lá Ògúmọ́lá, *Lànǹkẹ́ Ọ̀mu* sórí àwo rẹ́kọ́ọ̀dù. Ní àwọn ọdún 1970 sí 1980 ni gbigbé eré aláwàdà Moses Ọlâìyá sórí fọ́n-ọ̀n-rán/ téèpù káṣẹ́ẹ̀tì náà fẹsẹ̀ múlẹ̀.
- Ní ọdún 1967 ni Ìṣeré sórí ìwé eré onífọ́tò bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú eré Ogunde *Yoruba Ronu Atọ́ka* ni olórí nínú àwọn ìwé eré onífọ́tò náà. Ilé iṣẹ́ West African Book Publishers ni ó ṣàgbéjáde Atọ́ka láàrin ọdún 1967 sí 1991 (Àkàngbé, 2014). Òmíràn tí a tún rí tọ́ka sí ni *Ìbùkún Aláwàdá* tí Moses Ọláìyá jẹ́ agbátẹrù rẹ̀.

- Ọdún 1976 ni a lè sọ pé sínnimá/ fíìmù bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹwu. Eré *Àjàní Ògún,* tí Ọlá Balógun ṣàgbéjáde rẹ̀, ti ẹgbẹ́ eléré Duro Ladipọ àti Adé Afọláyan (Adé Love) jẹ́ òṣèré nínú rẹ̀ ni àkọ́kọ́ irú rẹ̀ (Ògúndèjì, 2014). Lẹ́yìn náà ni àwọn fíìmù *Ìjà Òmìníra, Kádàrá, Ọmọ Òrukàn, Ìyá Ni Wúrà, Ìjà Orogún, Taxi Driver I* àti *Taxi Driver II* tí Adéyẹmí Afọláyan ṣe. Ogunde ṣe sinimá bíi *Ayé, Jaiyesinmi, Àròpin N'Tènìyàn àti Àyànmọ́*. Bẹ́ẹ̀ sì ni Moses Adéjùmọ̀ náà ṣe *Ọ̀run Móoru* àti *Àrẹ Àgbáyé.*

  Àwọn fíìmù tí à ń wò lára ògiri nínú ilé sinnimá ni irú àwọn fíìmù tí wọ́n fi bẹ̀rẹ̀ fíìmù Yorùbá. Owó gegeege ni wọ́n máa ń wọ́n torí òkè okun ni wọ́n ti máa ń lọ fọ fíìmù náà lẹ́yìn tí wọ́n bá ti ya àwòrán rẹ̀ tán lórílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ eléré ni kò ní àǹfàní ẹ̀yáwó ní báńkì láti ṣe fíìmù.
- Ọdun 1988 ni Haynes àti Okome tọ pinpin ìbẹ̀rẹ̀ fídíò àgbélewò sí, nígbà ti oníṣòwò ọmọ ilẹ̀ Igbo kan ṣàgbéjadé fídíò àgbéléwò Ìshọ̀lá Ògúnṣọlá (I-show-Pepper) *Àjẹ́ Nìyá Mi* lowó pọ́ọ̀kú, (ẹgbẹ̀rún méjì náírà) tí ó sì jèrè ẹgbẹ̀lẹ́gbẹ̀ rọ́pò. Èyí ni ó mú kí àwọn eléré onílànà Ogúnde bí i jídé Kòsọ́kọ́ Adébáyọ̀ Sàlámì, Adébáyọ̀ Adéwùsì àti Muideeen Arómirẹ́ bẹ̀rẹ̀ sí í ṣàgbéjáde eré fídíò àgbéléwò ara tiwọn fúnra wọn nípa rírẹ́ǹtì àwọn irinṣẹ́ fún lílò. (Àlàmú, 2010).

## 5. 0 Ìsọníṣókí

- Nínú ìdáni lẹ́kọ̀ọ́ yìí ohun méjì ni a gbé yẹ̀wò. Àkọ́kọ́ ni àwọn oríṣiríṣi orúkọ tí àwọn onímọ̀ dá lábàá láti fi pe eré-oníṣe tí Ogunde sọ di gbajúgbajà. Ìkejì sì ni ọ̀rọ̀ nípa ìgbéǹde àtìdàgbàsókè irúfẹ́ ere oníṣe náà.
- Nígbà tí a gbé àwọn orúkọ náà lé orí òṣùwọ̀n ìṣèyàtọ̀ tàbí ìpààlà, a kíyèsí wí pé ìkankan nínú àwọn orúkọ náà kò múná dóko. Ìdí nìyí tí a fi fara mọ́ àbá Ògúndèjì (1987, 1988) pé kí a ṣàmúlò orúkọ Ogunde tí ó jẹ́ olùlànà irú ìṣeré náà: kí á máa pè é ní Eré oníṣe Onílànà Ogunde.
- Nínú àgbéyẹ̀wò ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè eré-oníṣe onílànà Ogunde a jíròrò lórí àwọn akitiyan tí ó ṣaájú ti Ogunde. Nípa lílo iṣẹ́ Ọ̀jọ̀gbọ́n Ẹ̀bùn Clark (1979) a ṣàlàyé nípa ìgbìyànjú Ogunde láti fi ẹsẹ̀ eré oníṣe náà múlẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà àmúṣiṣẹ́ kan gbòógì. A

wa wo ìdàgbàsókè tí ó ti dé bá ìlànà ìṣeré náà lápapọ̀ láti 1944 tí Ogunde kọ́kọ́ fara hàn lórí ìtàgé títí di ẹ̀yìn òmìnìra Nàìjíríà.

- Àkókò mẹ́ta gbòógì tí a ṣàlàyé pé ìdàgbàsókè náà pín sí ni ti oníjólórin (1944 -1950) ti kọ́ńsáàtì (1950 – 1965) àti ti bágbàmu (1965 – di òní-olónìí).
- Lábẹ́ ìjíròrò lórí ìdàgbàsókè àkókò bágbàmu a sọ̀rọ̀ lórí ìbúrẹ́ké ìṣeré lóríréḍíò, ìfẹṣẹ̀múlẹ̀ ìṣeré lórí tẹlifiṣàn àti àwo rẹ́kọ́ọ̀dù, ìdìdelẹ̀ ìseré sínú ìwé eré onífọ́tò, sínnimá àti fídíò àgbéléwò

## 6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàkọsílẹ̀ mẹ́rin nínú àwọn orúkọ tí àwọn onímọ̀ ti dá lábàá láti fi sọrí eré-oníṣe tí Ogunde sọ di gbajúgbajà.
2. Ṣe àlàyé àwọn ìdí pàtàkì tí àwọn orúkọ wọ̀nyí fi kùnà.
3. Kín ni ó mú Ògúndèjì dábàá láti pe eré náà ní "eré – oníṣe onílànà Ogunde àti àjọ òṣèré rẹ̀"?
4. Ṣe àlàyé ipò tí eré-oníṣe onílànà Ogunde wà láti ìbẹ̀rẹ̀ àkókò bágbàmu títí di lọ́ọ̀lọ́ yìí.

## 7. 0 Ìwé ìtọ́kasí


Adédèjì 1973. "The Church and the Emergence of the Nigerian Theatre: 1915-1945" *Journal of the Historical Society of Nigeria,* Fol. Vol. i. No. 4, o. i. 387-396.

Àkàngbé C. A. 2014. 'History, Production and Content of *Atọ́ka* Photoplay Magazine', Unpublished Ph. D. Thesis, University of Ibadan, Ibadan.

Àlàmú O. O. 2010. *Aesthetics of Yoruba Film*. Lingua-Culture Contextual Sudies in Ethnic Conflicts of the Wo/rld (LUCCOSEC) Vol. 10. Research Institute for World languages (RIWL), University of Osaka, Osaka.

Beier, U. 1954. 'Yorùbá folk Operas', *African Music*, vol. 1, no. 1, o. i. 32 – 43.

Clark, E. 1979. Hubert Ogunde: The Making of Nigerian Theatre. O.U.P. Oxford.

Jeyifo, B. 1981. *The Yoruba Professional Itinerant Theatre: Oral Documentation, vol II,* English edition, Mimeograph.

Jeyifo, B. 1984. *The Yoruba Popular Travelling Theatre of Nigeria*. Nigeria Magazine Publication, Lagos.

Ogunbiyi 1981. *Dama and Theatre in Nigeria: A Critical Sourc Book.* Nigeria Magazine Special Publication, Federal ministry Of Social Development Youth Sports and Culture, Lagos.

Ogundeji P. A. 1987. "Trends and Issues in the Ogunde Dramatic Tradition", *Review of English and Literary Studies*, Fol.14. 1. o. i. 69-94

Ogundeji, P. A. 1988 'A Semiotic Studies of Duro Ladipo's Mythico-Historical Plays', Unpublished Ph. D. Thesis, University of Ibadddan, Ibadan.

Ogundeji, P. A. 1992. *Yorùbá Drama 1(Eré-oníṣe Yorùbá 1*). Centre for External Studies University of Ibadan, Ibadan

Graham-White, A. 1974. *The Drama of Black Africa*, Samuel French Inc. New York.

## Ìpín 2: Àbùdá ìṣeré onílànà Ogunde: Ajẹmọ̀ṣeré àti ajẹmọ̀ lítíréṣọ̀

Ìlàpa èrò

1.0 Ìfáárà

2. 0 Èròńgbà

3. 0 Ìbéèrè ìṣaájú

4. 0 Àkóónú iṣẹ́

4. 1. 0 Àbùdá ajẹmọ̀ṣeré

4. 1. 1 Òṣèré

4. 1. 2 Ìpolongo eré

4. 1. 3 Ibi ìṣeré

4. 1. 4 Ìgbéréká

4. 1. 5 Àkójọ eré

4. 2. 0 Àbùdá ajẹmọ̀-lítíréṣọ̀

4. 2. 1 Ṣíṣẹ̀dá eré

4. 2. 2 Àhunpọ̀ ìtàn

4. 2. 3 Ìfìwàwẹ̀dá

4. 2. 4 Ìmúlò ewì

5. 0 Ìsọníṣókí

6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7. 0 Ìwé ìtọ́kasí

## 1. 0 Ìfáárà

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìlànà ìṣeré àwọn òṣèré onílànà Ogunde kò dúró rigidi sí ojú kan torí àtinúdá oríṣiríṣi tí àwọn òṣèré eré náà máa ń mú lò, èyí tí ó yàtọ̀ láti ọ̀dọ̀ ẹnìkan wọn sí èkèjì, síbẹ̀ a kò le fi gbogbo ẹnu sọ pé àwọn àjọ̀ òṣèré náà kò ní ìlànà kan gbòógì tí wọ́n ń tẹ̀lé gẹ́gẹ́ bí Jeyifo (1984) ṣe fẹ́ kí á gbàgbọ́. Ohun tí ó hàn gbangba ni pé àwọn ẹgbẹ́ òṣèré náà ní àwọn ìlànà ìṣeré tí wọ́n ń tẹ̀lé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìyípadà àtìgbàdégbà máa ń dé bá àwọn ìlànà náà. Abẹ́ ìsọ̀rí ńláńlá méjì tí a pín ìjíròrò wa nípa àwọn àbùdá eré-oníṣe onílànà Ogunde sí ní inú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni ti àbùdá ajẹmọ́ṣeré àti ti àbùdá ajẹmọ́ lítíréṣọ̀, bí ó ti hàn nínú àkọlé ìpín kejì inú módù kẹta yìí.

## 2. 0 Èròǹgbà

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìwọ gẹ́ggẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ yóò ti le ṣe àlàyé nípa oríṣiríṣi àwọn àbùdá eré-oníṣe onílànà Ogunde. O ó ti le jíròrò lórí:

- Àwọn àbùdá tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ìṣeré (bí i òṣèré, ìpolongo-eré, ibi ìṣeré, ètò ìṣeré, ìgbéréká àti àkójọ eré).
- Àwọn àbùdá tó ní í ṣe pẹ̀lú lítíréṣọ̀ (bí i ṣíṣẹ̀dá eré, àhunpọ̀-ìtàn, ìfìwàwẹ̀dá àti ìṣàmúlò ewì) nínú ìṣeré àti eré-onítàn onílànà Ogunde.

## 4. 0 Àkóónú iṣẹ́

### 4. 1. 0 Àbùdá ajẹmọ́ṣeré

- Bí ìlànà Ogunde ṣe mú lò nínú ìlànà ìṣeré ti àbáláyé, pàápàá ti eégún aláré, náà ni ó mú lò nínú ti òde òní.

- Àwọn ìlànà ajẹmọ́ṣeré tí ó fara hàn nínú ìṣeré-oníṣe onílànà Ogunde tí a gbé yẹ̀wò ni: òṣèré, ìpolongo eré, ibi ìṣeré, ètò ìṣeré, ìgbéréká àti àkójọ eré.

### 4. 1. 1 Òṣèré

- Bíi ti àwọn eégún aláré, ọ̀pọ̀ nínú àwọn òṣèré onílànà Ogunde ni ó jẹ́ aya, ọmọ mọ̀lẹ́bí àti ọ̀rẹ́ olórí ẹgbẹ́ eléré. Ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ìṣeré náà ni èyí ti hànde jù lọ. A fẹ́rẹ̀ lè sọ nígbà náà pé eré oníṣe náà jẹ́ iṣẹ́ ìdílé bí i teégún aláré.
- Nígbà tí ìṣeré eré oníṣe náà kọ́kọ́ ń dìdelẹ̀ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ àmúṣe, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni kò fẹ́ láti ṣe irú iṣẹ́ náà nítorí wọ́n gbà pé kò lérè, ó sì jẹ́ iṣẹ́ àbùkù. Ìdí nìyí tí àwọn olórí ẹgbẹ́ máa fi ń lo mọ̀lẹ́bí, ará àti ọ̀rẹ́ bí òṣèré.
- Nígbà ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ìṣeré yìí, wọn kì í tilẹ̀ rí òṣerébìnrin dàbíalárà, ọkùnrin ni wọ́n máa múra fún láti kópa obìnrin. Èyí ni ó fà á tí àwọn olórí ẹgbẹ́ eléré ṣe máa ń fẹ́ ìyàwó púpọ̀ láti máa bá wọn ṣiṣẹ́.

### 4. 1. 2 Ìpolongo eré

- Àwọn eléré onílànà Ogunde máa ń fi mọ́tò lọ́rì ẹgbẹ́ eléré wọn polongo eré onítàn tí wọ́n bá fẹ́ ṣe káàkiri ìlú tí wọ́n ti máa ṣeré. Wọn á máa lùlù, oníjó kan tàbí méjì (wọn lè lo ìbòjú tàbí ìmúra àrà ọ̀tọ̀) lè jókòó sóri ọkọ̀ náà kí wọ́ máa jó bí awakọ̀ ti ń ń wakọ̀ jẹ́jẹ́ yí poponà ìlú ká. Yatọ̀ sí orin kíkọ nírú àsìkò bẹ́ẹ̀, wọn ó máa kéde àkọlé eré wọ́n, ibi tí wọ́n yóò ti ṣe é àti àkókò tí wọn yóò ṣe é. Wọ́n máa ń lo ẹrọ gbohùngbohùn látiṣe eléyìí. Wọ́n sábàá máa ń ṣe èyí ní ó kọ̀la tí wọn ó ṣe eré náà àti lọ́jọ́ tí wọn ó ṣe é gangan. Eléyìí náà fi ara jọ bí àwọn eléégún aláré ṣe máa ń polongo eré oníṣe wọn. Ìlànà ìgbàlódé nípa lílo lọ́rì àti ẹrọ gbohùngbohùn tí asọ nìkan ni wọ́ fi yàtọ̀.
- Àwọn òṣèré onílànà Ogunde tún máa ń lo gbogbo ọ̀nà ìpolongo òde òní náà bíi lílẹ bébà ìpolongo ńláńlá káàkiri, híhá bébà ìpolongo kéékèèké àti ṣíṣe ìkéde sínú ìwé-ìròyìn, lórí rédíò àti tẹlifíṣàn náà.

### 4. 1. 3 Ibi ìṣeré

- Gẹ́gẹ́ bíi ti àwọn eléégún aláré, ó fẹ́rẹ̀ẹ́ má sí ibi tí ó tẹ́jú tàbí gbọ̀ngàn tí àwọn eléré onílànà Ogunde kò lè lò fún ìṣeré.
- Wọ́n lè ṣeré ní gbangba ìta tàbí inú gbọ̀ngàn ìlú, tilé ìwé, ṣọ́ọ̀ṣì pẹ̀lú ti hòtẹ́ẹ̀lì.
- Wọ́n tún máa ń ṣe eré lórí rédíò, tẹlifíṣàn, sinimá, fídíò àgbéléwò, àwo rẹ́kọ́ọ̀dù/ àwo mọ́ńbé (Síí Diì), fọ́n-ọ́n-rán kásẹ́ẹ̀tì pẹ̀lú inú ìwé eré-onífọ́tọ̀. [Wo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ Ìpín Kìn-ín-ní Módù Kẹta yìí fún alàyé nípa èyí.]
- Ó yẹ kí á tẹnu mọ́ ọn pé ipa ribiribi ni àwọn eléré onílànà Ogunde kó nínú ìdìdelẹ̀ àti ìdàgbà-sókè ìṣeré sóri rédíò, tẹlífíṣàn, ìwé eré onífọ́tò pẹ̀lú sinnimá àti fídíò tí wọ́n wá dí gbajúgbajà ní òde òní.

### 4. 1. 4 Ètò ìṣeré

- Àwọn òǹwòran kì í sáábà pagbo bí ó ti máa ń wáyé nínú ìṣeré eégún aláré.
- Bí ibi ìṣeré bẹ́ẹ̀ bá jẹ́ gbọ̀ngàn eré, orí pèpéle ìṣeré tí ó wà níwájú àwọn òǹwòran ni àwọn eléré ti máa ń ṣeré.
- Irú ètò ibi ìṣeré àtọ̀húnrìnwá yìí kò fi ààyè sílẹ̀ fún àjọṣe típẹ́típẹ́ láàrin òṣèré àti òǹwòran bí i ti inú eré eégún aláré.
- Gẹ́gẹ́ bí i ti àwọn eléré eégún aláré, àwọn eléré onílànà Ogunde náà sábà máa ń pín ètò ìṣeré wọn sí ọ̀nà mẹ́ta: orin ìṣíde eré, eré náà gan-an àti orin ìparí eré.
- Nínú orin ìṣíde ni wọ́n tí máa ń júbà Ọlọ́run àti àwọn ènìyàn, wọn á sì tún máa ta àwọn òǹwòran lólobó nípa àhunpọ̀-ìtàn eré tí wọ́n fẹ́ ṣe.
- Lẹ́yìn náà ni wọn óò tó ṣe eré gan-an.
- Nínú orin ìparí ni wọn óò ti fa àwọn ẹ̀kọ́ inú eré jáde, tí wọn óò wúre tí wọ́n ó sì dágbére pé àwọn ti ń lọ.
- Àwọn orin ìṣíde àti tìparí eré yìí gbajúmọ̀ gan-an nígbà tí eré yìí kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ ṣùgbọ́n nígbà tó yá, àwọn òṣèré kọ̀ọ̀kan ṣe ìyípadà díẹ̀ díẹ̀ sí i, àwọn kan kò sì lo àwọn orin náà mọ́. Dípò orin ìṣíde, ijó kábárẹ́ẹ̀tì tún ni àwọn eléré mìíràn bíi Moses Ọláìyá Adéjùmọ̀ tẹra mọ́ fún ìṣíde àti ìkádìí eré nílẹ̀

- Moses Ọláìyá kan náà tún gbìyànjú ṣíṣe àfihàn sinimá gẹ́gẹ́ bí ìtọ́nuwò láti ṣíde ìṣeré rẹ̀ nígbà kan. Ó tilẹ̀ máa ń fi sínnimá sínú àhunpọ̀-ìtàn eré rẹ̀ náà lórí ìtàgé nígbà míràn láti ṣàfihàn àwọn ìran tí ì bá jẹ́ ti ẹ̀yìn ìtàgé.

4. 1. 5 Ìgbéréká

- Láti ìbẹ̀rẹ̀ wá ni àwọn àwọn eléré onílànà Ogunde ti jẹ́ agbéréká bíi ti àwọn eléégún aláré.
- Ogunde ni òṣèré àkọ́kọ́ tí ó dá ìlànà yií láṣà ní ọdún 1948 nígbà tí ó fi iṣẹ́ ọlọ́pàá tí ó ń ṣe sílẹ̀ láti gbájú mọ́ eré ṣíṣe Òun ni olùlánà gbígbéré káàkiri orílẹ̀ èdè Nàìjíríà àti àwọn orílẹ̀ èdè Ìwọ̀ Oòrùn Áfíríkà fún àwọn yòókù.
- Gbọ̀ngàn ìlú, ti hòtẹ́ẹ̀lì, ilé-ìwé àti ṣọ́ọ̀ṣì pẹ̀lú iwájú ilé ọba àti gbangba ìta agboolé káàkiri ni àwọn ààyè tí wọn ń lò láti ṣeré nígbà náà.
- Nígbà tí fíìmù bẹ̀rẹ̀ àwọn ẹgbẹ́ eléré tí ó ti ṣe fíìmù náà a máa gbé fíìmù wọn káàkiri láti fi han àwọn òǹwòran wọn. Gẹ́gẹ́ bí a ti ṣo tẹ́lẹ̀ àwọn fíìmù àwò-lẹ́gbẹ̀ẹ́-ògiri nínú ilé sinnimá ni àwọn fíìmú ìgbà náà.

4. 1. 6 Àkójọ eré

- Gẹ́gẹ́ bí i ti àwọn eléégún aláré, ẹgbẹ́ eléré onílànà Ogunde kọ̀ọ̀kan ni ó máa ń ní àkójọpọ̀ eré onítàn tí wọ́n ti ṣe rí ní àrọ́wọ́tó, ìgbàkúùgbà sì ni wọ́n lè yan ọ̀kan tàbí méjì tí wọn óò máa gbé káàkiri.
- Kì í dín ní eré méjì lára àwọn eré-onítàn wọn tí wọ́n máa ń gbé káàkiri lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo.
- Ó yẹ kí á tún yán an bákan náà pé wọn a tún máa ní àkójọ aṣọ eré, ìlù oríṣiríṣi àti àwọn ohun èlò ìṣeré lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan. Nínú àwọn wọ̀nyí ni wọ́n ti máa ṣà lò fún ìṣeré tuntun.

4. 2. 0 Àbùdá ajẹmọ́-lítíréṣọ̀

- Àwọn àbùdá ajẹméré-oníṣe, gẹ́gẹ́ bíi lítíréṣọ̀, tí a ó gbé yẹ̀wò ni: ṣíṣẹ̀dá eré, àhunpọ̀-ìtàn, ìfìwàwẹ̀dá àti ìlò ewì.

4. 2. 1 Ṣíṣẹ̀dá eré

- Jíjẹ́ tí eré oníṣe onílànà Ogunde jẹ́ àpilẹ̀ṣe fààyè sílẹ̀ fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ àtinúdá nípa ṣíṣẹ̀dá eré. A lè sọ wí pé nípa ìfọwọ́sowọ́pọ̀ láàárín gbogbo àwọn òṣèré ni a ṣe máa ń sábà á ṣẹ̀dá ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn eré tí ó wà nínú àkójọpọ̀ ẹgbẹ́ eléré kan.
- Lóòótọ́ ni ó jẹ́ pé olórí ẹgbẹ́ ni ó máa ń sábà á ṣẹ̀dá àhunpọ̀-ìtàn eré oníṣe, tí yóò sọ ọ́ fún àwọn òṣèré rẹ̀, tí yóò sì yan ipa tí ọ̀kọ̀ọ̀kan nínú wọn yóò kó fún wọn ṣùgbọ́n òṣèré kọ̀ọ̀kan ní í máa lo àtinúdá ara rẹ̀ láti ṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ àti ìsínnijẹ tí yóò fi gbé ẹ̀dá ìtàn tí yóò sín jẹ náà kalẹ̀.
- Gẹ́gẹ́ bí olùdarí eré, olórí ẹgbẹ́ ni yóò máa ṣe àmójútó eré náà tí yóò máa ṣe àfikún àti àyọkúrò sí àtinúdá àwọn òṣèré wọ̀nyí, kí ìsínjẹ tí òṣèré bá fẹ́ gbé kalẹ̀ le bójú mu, kí ó sì ṣe rẹ́gí pẹ̀lú àmójú-sùn olùṣẹ̀dá àhunpọ̀ ìtàn.
- Bí ó tí jẹ́ pé àjùmọ̀-pawọ́pọ̀-ṣe ni púpọ̀ eré-onítàn àwọn eléré onílànà Ogunde yìí, ìbéèrè tí kò le ṣàìwáyé ni wí pé ta ni a ó sọ pé ó jẹ́ olùṣẹ̀dá eré ní pàtó. Níwọ̀n ìgbà tí ó jẹ́ pé gbogbo àwọn ọmọ ẹgbẹ́ eléré náà ni wọ́n dá ohun kan tàbí òmíràn jọ sínú eré náà nípasẹ̀ àtinúdá wọn; àwọn náà lẹ́tọ̀ọ́ láti gba oríyìn fún àtinúdá tí wọ́n dá jọ. Bí a bá fi ojú yìí wo ọ̀rọ̀ náà bóya gbogbo ẹgbẹ́ ni ó yẹ kí á máa sọ pé ó ni eré. Ìyẹn ni pé bí a bá mú eré *Awo Mímọ́* bí àpẹẹrẹ, a óò pè é ní eré ẹgbẹ́ Hubert Ogunde, a kò ní í sọ pé ó jẹ́ eré Hubert Ogunde nìkan.
- Ṣùgbọ́n bí a bá tún fi ojú mìíràn wo ọ̀rọ̀ náà, bí àwọn ọmọ ẹgbẹ́ tilẹ̀ dá ohun kan tàbí òmíràn jọ sínú eré, olórí ẹgbẹ́ eléré, tí ó ni ẹgbẹ́ náà ni a máa sọ pé ó ni eré-onítàn yìí. Yàtọ̀ sí pé òun ló ni ẹgbẹ́, òun ni ó tún ṣẹ̀dá àhunpọ̀-ìtàn, tí ó sì tún jẹ́ olùdarí eré. Òun ni ó sì máa ń ṣe gbogbo ìnáwó-nára ìgbéré kalẹ̀ lórí ìtàgé, bí ọ̀rọ̀ ẹjọ́ tàbí wàhálà kan bá sì jẹ yọ nípa eré tàbí ìṣeré náà, òun ni yóò jẹ́jọ́ tí yóò sì wá ọ̀nà láti yanjú wàhálàkíwàhálà, tí ì báà yọjú. Bí a bá fi ojú àrògún yìí wo ọ̀rọ̀ náà eré Ogunde ni a óò pe *Awo Mímọ́*.
- Àpẹẹrẹ àwọn olórí ẹgbẹ́ eléré àti eré wọn ni Hubert Ogunde (*The Garden of Eden and the throne of God, King Solomon, Ṣẹrankoṣenìyàn, Yorùbá Ronú, Tiger's Empire, Aiye, Aròpin Ntènìyàn,*); Kọ́lá Ògúnmọ́lá (*Má gbára Lé Wọn, Òrìṣà Jẹ́ N*

*Pé Méjì Obìnrin Kò Dénú, Igbó Olódùmàrè Làńkẹ́ Ọ̀mu, Ìfẹ́ Owó*); Dúró Ládipọ̀ (*Ọba Kò So, Mọrèmi, Ọbá Wàjà, Ajagun Nlá, Ọbàtálá, Olúwẹrí*); Oyin Adéjọbí (Kúyẹ̀, *Ìtọ́jú Kúnlé, Èkùrọ́ Ọlọ́jà, Tẹni N Tẹni*; Akin Ògúngbè (Bàbá Ìbejì, Ìrèké Oníbùdó.

### 4. 2. 2 Àhunpọ̀-ìtàn

- Ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ìṣeré onílànà Ogunde, àhùnpọ̀ ìtàn àwọn eré oníṣe àwọn eléré náà kì í gùn, kì í sì í sábà á lọ́jú; ó máa ń lọ tàárà ni, yálà eré náà jẹ́ tí orí ìtàgé, eré onítàn kúkùùkú lórí tẹlifíṣàn àti rédíò tàbí òmíràn.
- Ẹ̀yìnọ̀rẹ̀yìn ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe ẹyọ eré kan fún bí i wákàtí kan sí méjì àti fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọjọ́ lórí tẹlifíṣàn (ọ̀sẹ̀ mẹ́tàlá bí a ti sọ ṣaájú). Àhunpọ̀ ìtàn irú àwọn eré ẹ̀yìnọrẹ̀yìn yìí gùn, wọ́n sì lọ́jú, wọn kò sì lọ tàárà mọ́.
- Ní àkókò ìbẹ̀rẹ̀, tí àhunpọ̀-ìtàn inú eré-onítàn eré-oníṣe onílànà Ogunde kì í gùn, orin ìṣíde eré àti tìparí eré ni ó máa ń mú kí ìṣeré kún dáadáa kí àwọn òǹwòran sì máa gbádùn rẹ̀ dé ojú àmì.

### 4. 2. 3 Ìfìwàwẹ̀dá

- Níbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ìṣere wọn, àwọn eléré onílànà Ogunde kì í gbájú mọ́ ọ̀rọ̀ ìfìwàwẹ̀dá tó nǹkan.
- Gbígbé ìtàn tó dùn tó sì kọni lẹ́kọ̀ọ́ kalẹ̀ ní í máa jẹ wọ́n lógún.
- Àbùdá yìí kì í ṣe ti àwọn eléré onílànà Ogunde nìkan gbogbo àwọn oníṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ Yorùbá ni kì í fi bẹ́ẹ̀ kọbiara sí ìfìwàwẹ̀dá tó bí ó ti yẹ.
- Lóde-òní, eré tẹlifíṣàn tí ó gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọjọ́ kí ó tó parí àti eré sinimá pẹ̀lú fídíò ti ń mú kí àwọn eléré yìí máa tẹra mọ́ ọnà ìfìwàwẹ̀dá nínú eré-oníṣe wọn ju ti tẹ́lẹ̀ lọ.

### 4. 2. 4 Ìmúlò ewì

- Ìṣàmúlò ewì wọ́ pọ̀ nínú àwọn eré-onítàn eléré onílànà Ogunde, irú ewì bẹ́ẹ̀ lè jẹ́ èyí tí a kọ lórin, tí a fi ìwọ́hùn ìsàré kan tàbí òmíràn gbé kalẹ̀ tàbí èyí tí a sọ lọ́rọ̀.
- Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ, orin ni wọ́n tilẹ̀ fi máa ń gbé gbogbo ìsọ̀rọ̀ngbèsì inú eré-onítàn Onílànà Ogunde kalẹ̀ níbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀.

- Èyí mú kí àwọn eré bẹ̀ẹ̀ ní àwòmọ́ ewì ju àwọn yòókù lọ, ṣùgbọ́n lẹ́yìnọrẹyìn, ọ̀gangan ibi tí àhunpọ̀-ìtàn ti dé góńgó tàbí tí wọ́n ti fẹ́ fa kòmóòkun ọ̀rọ̀ kan yọ ni wọ́n ti máa ń lo orin.
- Ìlò ọfọ̀, àti àwọn ewì àwíṣẹ, ewì yẹ̀ńwò àti àwọn ewì àrángbọ̀ mìíràn tún wọ́pọ̀ nínú eré-onítàn àwọn eléré onílànà Ogunde, ó  sì jẹ́ ọnà pàtàkì nínú eré náà. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, bí a bá wo eré *Yorùbá Ronú*, nígbà tí àwọn ẹrú Yèyé Ìlọbà fẹ́ bí agbára rẹ̀ ṣe tó hàn, bí wọ́n ṣe lo orin tí ó ní oríkì nínú láti fi kì í nìyí ní ìsàlẹ̀ yìí:

  Yèyé olóró ni Yèyé àwa

  Yèyé ò makọ

  Yèyé ò mabo

  Ò dẹrù ọmọ ọlọ́mọ nù

  Fomi ata bọ́jú

  Afìkòkò ńlá dáwọn lẹ́kun àfojúdi...

- Wọ́n fi hàn nínú oríkì yìí pé ọ̀dájú ènìyàn, àjẹ́ àti ìkà ènìyàn gbáà ni ìyá náà. Wọ́n tilẹ̀ tún kọ ọ́ lórin pé ògbójú àjẹ́ ni Yèyé Ìlọbà. Àmúlò àrángbọ̀ àti orin níbí yìí jẹ́ àmúlò ewì.

## 5. 0 Ìsọníṣókí

- Bí àgbálọgbábọ̀, ó yẹ kí á tọ́ka sí i wí pé, àwọn àbùdá wọ̀nyí ti ń yí padà díẹ̀díẹ̀ gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe mẹ́nu bà á nínú àwọn àlàyé wa lókè. Bí àwọn ẹgbẹ́ eléré wọ̀nyí bá pa ìlànà kan tì, ìlànà mìíràn tó dára ju èyí tí wọ́n tí ń lò tẹ́lẹ̀ lọ ni wọ́n máa ń fi rọ́pò. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, wọn a máa fi mọ́tò polongo eré wọn nígbà ìbẹ̀rẹ̀ ìṣeré, orí ìtàgé nìkan ni wọ́n sì tí máa ń ṣeré. Nígbà tí ó yá wọ́n fi ìpolongo àti ìṣeré sórí rédíò, tẹlifíṣàn àti lẹ́yìn-ọ̀rẹyìn lórí ìtàkùn àgbáyé kún un, pàápàá láyé fídíò àgbéléwò yí.
- Àdínkù ti bá lílo ọgbọ́n àtinúdá ẹni láti gbé ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì inú eré kalẹ̀ láyé fídíò àgbéléwò  nítorí ìṣàmúlò àkọsílẹ̀ eré tòuntìsọ̀rọ̀ǹgbèsì inú rẹ̀ tí àwọn òṣeré gbọ́dọ̀ tẹ̀lé. Látìgbà ìṣeré lórí tẹlifíṣàn ni èyí ti bẹ̀rẹ̀ díẹ̀díẹ̀. Bákan náà, dandan kọ́ ni kí òṣèré dara pọ̀ mọ́ ẹgbẹ́ kan ní pàtó kó tó ṣeré fídíò mọ́ lóde òní. Àwọn ìlànà ìṣeré òde òní yàtọ̀ sí ti àtijọ́.

- Ìsọ̀rí ńláńlá méjì tí a pín ìjíròrò wa nípa àwọn àbùdá eré-oníṣe onílànà Ogunde sí ní inú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni tàbùdá ajẹmọ́ṣeré àti tàbùdá ajẹmọ́ lítíréṣọ̀.
- Lábẹ́ àbùdá ajẹmọ́ṣeré a ṣàgbéyẹ̀wò òṣèré, ìpolongo eré, ibi ìṣeré, ètò ìṣeré, ìgbéréká àti àkójọ eré oníṣe.
- Awọn àbùdá ajẹmọ́ lítíréṣọ̀ tí a jíròrò lé lórí ni ṣíṣẹ̀dá eré, àhunpọ̀-ìtàn, ìfìwàwẹ̀dá àti ìṣàmúlò ewì.

6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Dárúkọ ìsọ̀rí ńlá ńlá méjì tí a pín àwọn àbùdá eré-oníṣe onílànà Ogunde sí.
2. Kín ni ìdí tí àwọn olórí ẹgbẹ́ eléré onílànà Ogunde fi maa ń lo àwọn mọ̀lẹ́bí àti ọ̀rẹ́ wọ́n bí òṣèré ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ irúfẹ́ ìṣeré wọn?
3. Ní ṣókí ṣókí ṣókí, ṣe àlàyé ọ̀nà méjì tí èrò pín sí lórí ṣíṣẹ̀dá eré onílànà Ogunde, kí o sì jẹ́ kí á mọ èyí tí o fara mọ́ jù lọ àti ìdí tí o fi fara mọ́ ọn.

7.0 Ìwé ìtọ́kasí

Jeyifo, B. 1984. *The Yoruba Popular Travelling Theatre of Nigeria*. Nigeria Magazine Publication Ministry of Youth, Transport and Culture, Lagos.

Ogundeji, P.A. 1987. "Trends and Issues in the Ogunde Dramatic Tradition", *Review of English and Literary Studies*, Fol. 4.1. o. i. 69 – 94.

## Ìpín 3: Ìpínsísọ̀rí eré-oníṣe onílànà Ogunde

### Ìlàpa èrò

1. 0 Ìfáárà

2. 0 Èròńgbà

3. 0 Ìbéèrè Ìṣaájú

4. 0 Àkóónú iṣẹ́

4. 1 Ìpínsísọ̀rí eré

4. 2. 0 Àlàyé eré àti àpẹẹrẹ

4. 2. 1 Eré adáléri ìtàn Bíbélì

4. 2. 2 Eré adáléri lítíréṣọ̀ mìíràn

4. 2. 3 Eré adáléri ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́

4. 2. 4 Eré-oníṣe adáléri ìtàn Yorùbá

5. 0 Ìsọníṣókí

6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7. 0 Ìwé ìtọ́kasí

## 1. 0 Ìfáárà

Oríṣìíríṣìí ni àwọn kókó ọ̀rọ̀ tí eré-oníṣe onílànà Ogunde máa ń dá lé nígbà tí eré náà kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀. Ṣíwájú Ogunde, ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn ọmọlẹ́yìn Krístì, ọ̀làjú òde-òní àti àṣà ilẹ̀ òkèèrè máa ń jẹ yọ nínú àwọn eré ìgbà náà, kódà èdè Gẹ̀ẹ́sì ni wọ́n fi máa ńṣe gbogbo ere látòkè délẹ̀. Nígbà tí ìpè gbígbé àṣà ilẹ̀ baba ẹni lárugẹ bẹ̀rẹ̀ sí ní í gbilẹ̀ ni ọ̀rọ̀ fífí ẹwà àṣà abínibí ọmọ Yorùbá hàn nínú àwọn eré onílànà Ogunde náà bẹ̀rẹ̀ sí ní í gbilẹ̀. Èyí ni ó sì bí eré D. A. Oyedele méjì *King Eléjìgbò and Princess Àbẹ̀jẹ́ of Kontangora* àti *The Jealous Queen Ọya of Ọyọ*, ti Olympus Moore, *Aṣìka Bí Àparò* àti ti I. B. Akínyẹlé, *Àwọn Ìwàrẹ̀fà Mẹ́fà* tí a t mẹ́nu bà ṣaájú. Àwọn eré tí a dárúkọ wọ̀nyí ni àkọsílẹ̀ fi yé wa pé wọ́n jẹ́ eré  ní èdè Yorùbá àkọ́kọ́, bí wọ́n tilẹ̀ kọ àkọlé àwọn kan nínú wọn ní Gẹ̀ẹ́sì. Ní kété tí Ogunde bẹ̀rẹ̀ eré, eré-oníṣe tó dá lé orí ìtàn inú Bíbélì ló fi bẹ̀rẹ̀. Èyí náà jẹ́ eré tó dá lé ẹ̀sìn ọmọlẹ́yìn Krístì. Ogunde àti àwọn alátẹ̀lé rẹ̀ ṣe eré ajẹmọ́tàn Bíbélì yìí dé gbèdéke àkókò kan kí wọ́n tó bẹ̀rẹ̀ sí níí máa ṣe eré oríṣìí mìíràn bí àwọn eré tó fi ìtàn, àṣà àti èrò Yorùbá hàn. Bákan náà ni wọ́n tún ṣe eré tó fi àṣà Yorùbá mọ́ tòde òní hàn, èyí ni àwọn eré ajẹmọ́ṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ àwùjọ. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àwọn ọ̀wọ́ tí a le pín àwọn eré-oníṣe onílànà Ogunde sí ni a gbé yẹ̀ wò. Ọ̀ṣùwọ̀n pàtàkì tí a lò fún ìpínsísọ̀rí/ìpínsọ́wọ̀ọ́ náà ni orísun eré àwọn òṣèré eré-oníṣe onílànà Ogunde.

## 2. 0 Èròǹgbà

Ní òpin ìkọ́ni yìí, ìwọ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́ yóò ti le:

- ṣe ìpínsísọ̀rí, àwọn eré-oníṣe onílànà Ogunde.
- jíròrò  nípa Ọ̀ṣùwọ̀n ìṣàmúlò fún ìpínsísọ̀rí àti àwọn ohun míìràn.
- ṣe àpẹẹrẹ àwọn eré tí ó wà ní ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan.
- ṣe àlàyé ìwọnúbọnú tí ó wà nínú ìpínsísọ̀rí náà.

## 3. 0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Ìsọ̀rí mélòó ni o lè pín eré àwọn onílànà Ogunde sí?
2. Ṣe ìdámọ̀ àwọn ìsọ̀rí náà.
3. Irú eré wo ni Dúró Ladipọ tẹra mọ́ jù lọ, ìrú èwo sì ni Ògúnmọ́lá tẹra mọ́ jùlọ?

## 4. 0 Àkóónú iṣẹ́

### 4. 1. 0 Ìpínsísọ̀rí eré

- Orísun àwọn àhunpọ̀ ìtàn inú eré-onítàn Onílànà Ogunde ni ọ̀ṣùwọ̀n tí a lò fún ìpínsísọ̀rí wa. Èyí túmọ̀ lílo ọ̀gangan ipò/ ibi tí àwọn olùṣẹ̀dá eré ti máa ń fa ìtàn eré wọn yọ.
- Ọ̀nà mẹ́rin tí a lè pín eré-oníṣe onílànà Ogunde sí tí a bá lo ìlànà ọ̀ṣùwọ̀n ìpínsísọ̀rí yìí ni: eré-oníṣe adálérí ìtán Bíbélì, eré-oníṣe adálérí ìtàn inú ìwé lítíréṣọ̀ mìíràn, eré-oníṣe adálérí ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ àti eré-oníṣe adálérí ìtàn Yorùbá.

### 4. 2. 0 Àlàyé àti àpẹẹrẹ

- Ó yẹ kí á yán an láti ìbẹ̀rẹ̀ ní ìhín pé, àwọn eré tí a óò mú lò jù lọ láti fi ṣe àlàyé àti àpẹẹrẹ yóò wá láti inú eré Ogunde fúnra rẹ̀, Oyin Adéjọbí, Kọ́lá Ògúnmọ́lá, Dúró Ladipọ àti Moses Ọláìyá Adéjùmọ̀. Lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan, níbi tí ó bá yẹ, a óò máa mú àwọn mìíràn náà lò ṣá.
- Ohun tí ó jẹ́ kí èyí rí bẹ́ẹ̀ ni pé àwọn wọ̀nyí jẹ́ gbajúgbajà ọ̀ṣèré eré-oníṣe onílànà Ogunde nígbà ayé wọn. Lẹ́yìn Ogunde, àwọn mẹ́rin tí a dárúkọ wọ̀nyẹn ni a tún le rí gẹ́gẹ́ bí aṣíwájú nínú ìṣeré onílànà Ogunde. Ìlúmọ̀ká ni wọ́n nígbà ayé wọn, bẹ́ẹ̀ ni àkọsílẹ̀ sì tún wà nípa akitiyan ìṣeré wọn, ẹgbẹ́ eléré àti eré pẹ̀lú.

### 4. 2. 1 Eré adéléri ìtàn Bíbélì.

- Orí àwọn ìtàn inú bíbélì ni olùṣẹ̀dá eré yóò gbé àhùnpọ̀ ìtàn eré rẹ̀ lé tí ó bá fẹ́ kọ eré adáléri ìtàn Bíbélì. Nígbà míràn olùṣẹ̀dá lè ṣe àyípadà sí ìtàn náà bí ó ti wà nínú Bíbélì níbàámu pẹ̀lú àmójúsùn ajẹmọ́nà tí ó bá ní lọ́kàn. Nígbà míràn wọn a sì maá ṣe é ní ìbamu pẹ̀lú ìtàn náà bí ó ti wà nínńú bíbélì gẹ́lẹ́, tàbí kí ó jẹ́ àyípadà díẹ̀ péré ni yó wà nínú rẹ̀.

- Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni àfojúsùn àwọn olùṣẹ̀dá àhunpọ̀ ìtàn eré bẹ́ẹ̀ máa ń jẹ́ láti fi jẹ́ iṣẹ́ ìjíyinrere. Èyí lè má rí bẹ́ẹ̀ nígbà míràn pàápàá nígbà tí àyípadá àti àfikún inú àhunpọ̀ ìtàn náà bá pọ̀ ju ti ìtàn Bíbélì tí olùṣẹ̀dá eré náà mú lò lọ. Ogunde tó jẹ́ ẹni tó tẹra mọ́ ìlànà yìí ti fi ìgbà kan jẹ́ olùdarí ẹgbẹ́ akọrin ní ilé ìjọsìn rẹ̀ rí. Bákan náà ni Dúró Ladipọ àti Oyin Adéjọbí. Kọ́lá Ògúnmọ́lá náà jẹ́ ọmọlẹ́yìn Krístì àti olùkọ́ àgbà ní ilé ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti ìjọ ọmọlẹ́yìn Jésù. Èyí ló mú àmúlò ìlànà náà rọrùn fún wọn. A ti mẹ́nu bá eré ajẹmọ́tàn Bíbélì tí Ogunde ṣe nígbà tí à ń jíròrò lórí ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè eré-oníṣe onílà Ogunde nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kìn-ín-ní nínú módù kẹta yìí. Nítorí náà àwọn eléré yòókù ni a ó fi ṣe àpẹẹrẹ báyìí. [Lọ padà wo àpẹẹrẹ ti Ogunde fúnra rẹ̀]
- Àwọn eré-oníṣe Oyin Adéjọbí tó jẹ mọ́ ìtàn inú Bíbélì ni *Paradise Lost* tí ó jẹ́ ìtàn Ádámù àti Eéfà, tó wà nínú Gẹ́nẹ́sis 1 – 3, *Path to Prominence* tó jẹ́ ìtàn bí Dẹlila ṣe dalẹ̀ Sámúsìnì alágbára, tí ó jẹ́ ọkọ rẹ̀ (Àwọn Onídàájọ 16), *Hannah's Trial and Triumph* tó jẹ́ ìtàn bí Ọlọ́run ṣe fún Hannah tí kò rọ́mọ bí tẹ́lẹ̀ ní ọmọkùnrin kan tí ó sọ ní Sámúẹ́lì, tí ojú sì ti ìyáálé rẹ̀ Pẹ̀línà tí ó máa ń fi ṣe yẹ̀yẹ́ tẹ́lẹ̀ (I Samuẹli 1-2) àti *Ayaba Esiteri* tó jẹ́ ìtàn bí Ọlọ́run ṣe sọ Esiteri tí ó jẹ́ ẹrú tẹ́lẹ̀ di ayaba tí ó sì lò ó láti gba àwọn ọmọ Israeli sílẹ̀ lọ́wọ́ ikú (Esther 2). Àwọn eré-onítàn yìí ni Oyin Adéjọbí fi bẹ̀rẹ̀, oníjólórin ni gbogbo wọn.
- Àpẹẹrẹ eré-oníṣe Kọ́lá Ògúnmọ́lá tó jẹ́ eré adáléri ìtàn inú Bíbélì ni *Reign of the Mighty* (ìtàn Nébukadinésarì, ọba Bábílónì tí ó gberaga sí Ọlọ́run; Dáníẹ̀lì 4: 25 – 35)*; Joseph and Brethren* (Ìtàn Jósẹ́fù, alálàá àti àwọn arákùnrin rẹ̀, Jẹ́nẹ́síìsì 37 – 50); *Hannah's Trial* (Ìtàn Hánà, Pẹ̀línà àti Ẹlikénà, ọkọ wọn Samúẹ́lì Kìn-ín-ní 1: 2 – 20); *Ọjọ́ ìbí Kristi* (ìtàn ìbí Jésù, Lúùkù 2: 1 – 20).
- Bí a ba wo àkọlé àwọn eré-onítàn Bíbélì Hubert, Ogunde, Oyin Adéjọbí àti Kọ́lá Ògúnmọ́lá dáradára, á ó kíyèsi pé èdè Gẹ̀ẹ́sì ni wọ́n fi kọ púpọ̀ nínú wọn. Èyí wà ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà àwọn òṣèré onílànà Ogunde ní ìgbà ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ bí a ti sọ síwájú.
- Àwọn eré Dúró Ládiípọ̀ tó dá lé orí ìtàn Bíbélì ni *Kọ bí idì* tí ó jẹ jáde láti inú ìtàn Dafidi àti Gòláyáàtì (1Samuel 1, 17), *Jálẹ̀yẹmí* tí ó jẹ́ ìtàn tí ó fà yọ láti inú ìtàn

Sámúsìnnì àti Dẹ̀lílà (Onídájọ́ 16) àti *Afọláyan* tí ó jẹ jáde láti inú ìtàn Jósẹ́fù aláàlá (Genesis 37 – 35).

- Ó yẹ kí á kíyè sí i wí pé, Dúró Ládiípọ̀ kò tẹ̀lé ìlànà fífún eré tí a mú jáde láti inú ìtàn Bíbélì ní àkọ́lé èdè Gẹ̀ẹ́sì ní tirẹ̀. Ní àfikún sí èyí ènìyàn kò lè tètè mọ̀ wí pé eré Bíbélì ni àwọn eré náà láti inú àkọlé wọn. Ó fi èyí yàtọ̀ sí àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ tí ó jẹ́ pé bí a bá ti rí àkọlé eré wọn ni a óò ti mọ̀ wí pé eré tí a fà yọ láti inú Bíbélì ni wọ́n. Ohun tí ó bí èyí ni pé Dúró Ládiípọ̀ ni ó gbìyànjú láti dá aṣọ àṣà Yorùbá ró àwọn ìtàn inú Bíbélì wọ̀nyí jùlọ láàárín àwọn yòókù. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìtàn inú Bíbélì ni àhunpọ̀ ìtàn inú eré rẹ̀ gùn lé, ó ṣe àyípadà sí ìtàn bíbélì náà dáadáa láti sọ ọ́ di àhunpọ̀ ìtàn eré rẹ̀. Èyí a sì máa fara hàn nínú àkọ́lé tó fún wọn gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i.

## 4. 2. 2 Eré adáléri ìtàn ìwé lítíréṣọ̀ mìíràn

- Àwọn eré tí ó dá lérí ìtàn inú ìwé lítíréṣọ̀ mìíràn jẹ́ àwọn ọ̀wọ́ eré tí àwọn eléré onílànà Ogunde fà yọ láti inú àwọn ìwé lítíréṣọ̀ tí àwọn òǹkọ̀wé mìíràn kọ. Èyí le jẹ́ lítíréṣọ̀ ilẹ̀ òkèèrè bí ti ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì, tàbí èyí tí wọ́n fà yọ láti ìwé lítíréṣọ̀ ilẹ̀ Nàìjíríà (pàápàá Yorùbá). Wọ́n a máa ṣe àyídà ìtàn ìwé lítíréṣọ̀ náà láti sọ ọ di àhunpọ̀ ìtàn eré wọn ní ọ̀pọ̀ ìgbà. Irú ìwé lítíréṣọ̀ tí wọ́n máa ń ti ṣe àfayọ àhupọ̀ ìtàn eré wọn náà lè jẹ́ ìwé ìtàn-àròsọ tàbí ti ìwé eré-oníṣe.
- Ìwé lítíréṣọ̀ tí Oyin Adéjọbí yí dà sí àwọn eré rẹ̀ ni *Kúyẹ̀ Ọmọ Òkú Ọ̀run*, àti *Ilé tí A fi Itọ́ Mọ*. Ìwé ìtàn àròsọ ni méjì àkọ́kọ́; *Kúyẹ̀ àti Ọmọ Òkú Ọ̀run*, nígbà tí *Ilé tí a fi Itọ́ Mọ* jẹ̀ eré-oníṣe.
- Nígbà tí Oyin Adéjọbí ṣe àmúlò àwọn ìwé ìtàn àròsọ J. F. Ọdúnjọ, *Kúyẹ̀* àti *Ọmọ Òkú Ọ̀run* fún àtẹ̀gùn eré rẹ̀, ó ṣe àyídà tí ó lọ̀ọ̀rìn sí àwọn ìtàn inú ìwé ìtàn àròsọ náà, kí ó tó lè sọ ọ́ di àhunpọ̀ ìtàn eré-onítàn tirẹ̀. Ìwọ̀nba ni akitiyan ìṣàyídà tí Oyin Adéjọbí nílò láti ṣe sí ìtàn inú ìwé eré-onítàn Olú Dáramọ̀lá, *Ilé tí A fi Itọ́ Mọ* nítorí pé ìwé eré-onítàn ni tẹ̀lẹ̀tẹ̀lẹ̀. A kò lè fi wé èyí tí ó ṣe sí ìtàn àròsọ *Kúyẹ̀* àti *Ọmọ Òkú Ọ̀run*.

- *Kúyẹ̀* náà ni àkọlé tí Oyin Adéjọbí fún eré rẹ̀ tí ó fà yọ láti inú ìwé ìtàn àròsọ J. F. Ọdúnjọ tí àkọlé rẹ̀ náà ń jẹ́ *Kúyẹ̀*. *Ìtọ́jú Kúnlé* ni àkọlé tí Oyin Adéjọbí yí ìtàn àròsọ *Ọmọ Òkú Ọ̀run* padà sí, ṣùgbọ́n kò ṣe àyípadà sí àkọlé eré Dáramọ́lá.
- Ìṣẹ̀lẹ̀ ìgbésí ayé *Kúyẹ̀* ní ilé Òjó àti Àlàbí ni Oyin Adéjọbí sọ di ọ̀kan ṣoṣo nínú eré-onítàn tirẹ̀. Kò sì ṣe àmúlò àwọn ìrírí ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó rọ̀ mọ́ Àdìó, Ìyábọ̀, Àdìgún Ọdẹ atamátàṣé àti Kogi nínú àyídà tí ó ṣe sí ìtàn-àròsọ náà. Eléyìí ni ó jẹ́ kí àhunpọ̀-ìtàn rẹ̀ ṣù pọ̀ dáradára nínú eré onítàn yìí tí kò fi wà lábalábala gẹ́gẹ́ bí ó ti rí ní inú ìwé ìtàn àròsọ náà.
- Àpẹẹrẹ àwọn eré Kọ́lá Ògúnmọ́lá tí ó mú láti inú ìtàn ìwé lítíréṣọ̀ mìíràn ni *The Palmwine Drinkard* (*Làńkẹ́ Ọ̀mu*) àti *Àdììtú Olódùmarè*. Amos Tutùọlá ni ó kọ ìtàn àròsọ *The Palmwine Drinkard*. D. O. Fágúnwà ni ó sì kọ ìwé ìtàn àròsọ *Àdììtú Olódùmarè*.
- Àpẹẹrẹ eré onítàn Dúró Ládipọ tí ó fà yọ látinú àwọn ìwé lítíréṣọ̀ mìíràn ni *Ẹ̀dá*. Látinú eré ayé àtijọ́ kan ní èdè Gẹ̀ẹ́sì tí ó ń jẹ́ *Everyman* ni ó fa á yọ. Bákan náà ni eré rẹ̀ *Ọ̀tún Akọgun* àti *Ọmọnidẹ* tó jẹ́ àyídà eré Shakespeare, *Macbeth* àti *As You Like it*.

### 4. 2. 3 Eré-oníṣe adáléri ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́

- Àwọn yìí jẹ́ eré tí ó máa ń dá lé orí ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ tó máa ń ṣẹlẹ̀ láwùjọ. Èyí le jẹ́ nípa ìfẹ́ àfẹ́jù tí àwọn ènìyàn máa ń ní sí owó àti obìnrin, ìwà ọ̀dàlẹ̀, oyè dídù, ìwà ìdàlúrú, ìrẹ́nijẹ abbl. Lára irú eré bẹ́l tí ogunde ṣe ni *Morẹ́nikẹ́, My Darling Fatima, Ile ìwòsàn, Olówó Òjijì, Màmá Èkó, Onímọ́tò* àti *Kẹ̀yìn Sókun*
- Ó fẹ́rẹ̀ jẹ́ pé ọ̀wọ́ eré oníṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ yìí ni ó wọ́pọ̀ jù lọ nínú àwọn eré-onítàn Oyin Adéjọbí. Àpẹẹrẹ eré-oníṣe Oyin Adéjọbí adáléri ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ ni *Tẹni N Tẹni, Orogún Adédigba, Èkùrọ́ Ọlọ́jà* àti *Láníyọnu*. Àwọn eré rẹ̀ tó jẹ́ ọ̀wọ́ eré orí tẹlifíṣàn tó jẹ mọ́ ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ ni *Kóòtù Aṣípa, Ilé Ìwòsàn* àti *Lábúlé wa*.
- Ọ̀rọ̀ oyè dídù àti ìwà jàǹbá tí àwọn ọmọ oyè máa ń hù sí ara wọn ni Oyin Adéjọbí gbé yẹ̀ wò nínú eré-oníṣe *Èkùrọ́ Ọlọ́jà*. Làágbé ni ọmọ oyè tí òun àti Adétòkunbọ̀ jọ ń du oyè. Tóògùn ọ̀rẹ́ Làágbé ló sì ń ràn án lọ́wọ́ kí oyè lè já mọ́ ọ́n lọ́wọ́. Ṣùgbọ́n

Díẹ̀kọ́lá ìyàwó Làágbé wé irọ́ mọ́ Tóògùn lẹ́sẹ̀ torí pé ìyẹn ká a mọ́ ìdí àgbèrè. Tóògùn kò rí ara rẹ̀ fọ̀ mọ́, ó sì di èrò oko níbi tó ti ó sá lọ fara pamọ́ sí. Níbẹ̀ ni ó ti rí èkùrọ́ ọlọ́jà kan he níbi tí ó ti ń kọ ebè. Èkùrọ́ ọlọ́jà yìí ni àwọn afọbajẹ ní kí àwọn ọmọ oyè lọ wá wá; wí pé ẹni tí ó bá kọ́kọ́ rí i nínú àwọn méjèèjì ni yóò jẹ ọba. Gbogbo ète Díẹ̀kọ́lá láti fi ọgbọ́n gba èkùrọ́ tí Tóògùn rí he nínú oko ló já sí pàbó. Báyìí ni Tóògùn fi èkúrọ́ ọlọ́jà fún Tokunbọ̀ ọmọ oyè kejì. Èyí ló sì sọ ọ́ di ọba. Ìwọ̀nyí jẹ́ fífi ìwà àrékérekè àwọn èniyàn sí ara wọn hàn.

- Àwọn eré-onítàn Kọ́lá Ògúnmọ́lá tó gùn lé orí ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ láwùjọ ni *Ìfẹ́ Owó, Òfo Àgbá* àti *Bíkà Kúure Kò Ní í Sùnunre*.
- Nínú *Ìfẹ́ Owó* ni Kọ́lá Ògúnmọ́lá ti fi han òǹwòran rẹ̀ pé ọ̀rẹ́ dáradára ni ọ̀rẹ́ tí ó bá ń gba ìkejì rẹ̀ nímọ̀ràn nípa àwọn àṣìṣe tí ó bá ń hù níwà, tí ó sì lè fa ìparun bá a. Àwọn ọ̀rẹ́ Adélékè gbà á níyànjú pé kí ó rọra jayé, kí ayé má baà jẹ ẹ́. Wọ́n kìlọ̀ fún un pé kí ó yàgò fún obìnrin àsìkò sùgbọ́n kò gbọ́. Ó tilẹ̀ lé Morọ́láyọ̀ tí í ṣe ìyàwó àárọ̀ rẹ̀ jáde tọmọtọmọ nítorí Mopélọ́lá ìyàwó ọ̀sán gangan tí ó wá gbé e lágbèédá nígbẹ̀yìn ọ̀rọ̀. Àìtẹ̀lé ìmọ̀ràn àwọn ọ̀rẹ́ gidi yìí ni ó fa ìṣubú Adélékè.
- Àpẹẹrẹ àwọn eré Dúró Ládipọ̀ tí ó jẹ mọ́ ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ láwùjọ ni *Gbádégẹṣin, Alágbára Má Mèrò, Má Gbára Lé Wọn, Sùúrù Baba Ìwà, Ìgbéraga Ni í Ṣíwájú Ìparun, Ọlọ́gbọ́n Ayé* àti *Òmúlẹ̀mófo*. *Eré Bodè Wásinmi* tí wọ́n ṣe lọ́wọ̀ọ̀wọ́ lórí tẹlifíṣàn náà wà ní ìsọ̀rí yìí.
- Moses Ọláìyá náà kò gbẹ́yìn nínú ṣíṣe irú àwọn eré yìí. Apẹẹrẹ ni *Ọmọlóòkú, Tòkunbọ̀, Ọmọ́ Wáṣẹ́, Sugar Daddy, Ìwé Ofin, Àbóo Yó, Ọ̀rún Móoru* abbl. Àwọn ọ̀wọ́ eré tẹlifíṣàn rẹ̀ *Aláwàdà* àti *My Pikin Friday* náà wà lára ọ̀wọ́ yìí.
- Gbogbo àwọn wọ̀nyí jẹ́ eré tí ó máa ń dá lé orí ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ kan tàbí òmíràn.

### 4. 2. 4 Eré-oníṣe adáléri ìtàn Yorùbá

- Eyí ni àwọn eré-oníṣe tí ó jẹ́ pé orí ìtàn ìbílẹ̀ Yorùbá, yálà ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi, tìwáṣẹ̀, takọni-kàyéfì tàbí tàlọ́-onítàn, ni a gbé wọn kà. Àwọn eléré le ṣe àyídà ìtàn wọ̀nyí tàbí kí wọ́n gbé e kalẹ̀ bí ó ṣe rí gẹ́lẹ́ nínú ìtàn náà.

- Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ogunde ti ṣe àwọn eré-onítàn ìbílẹ̀ kan bí *Igbó Irúnmọlẹ̀, Ṣẹranko* - ṣenìyàn àti *Ìbejì Méjì* ṣaájú, síbẹ̀ Dúró Ladipọ ni ó gbajúmọ̀ julọ fún irú eré bẹ́ẹ̀ ní ṣíṣe. Àkíyèsí tí Ògúndèjì ṣe nínú iṣẹ́ ìwádìí rẹ̀ sí eré Dúró Ladipọ̀ fi hàn pé gbogbo àwọn eré rẹ̀ yòókù ni ó máa ń ní àbùdá àfijọ eré adálérí ìtàn ìbílẹ̀ Yorùbá.
- Eré Dúró Ládipọ tí ó jẹ́ onítàn ìbílẹ̀ Yorùbá ni *Ọba Mọ́rọ̀, Ọba kò So, Ọbá Wàjà, Ọbàtálá, Ọ̀ṣun, Ajagun-ńlá, Mọ́rèmí, Béyìí ò Ṣe, Olúwẹri, Ọ̀rúnmìlà, Ògèdèǹgbé, Ewé Ayọ* abbl.
- Eré *Ọba Kò So* tí ó gbajúmọ̀ jù lọ láàrin àwọn ọ̀wọ́ eré yìí ṣe àfihàn èdè àiyedè tí ó bẹ́ sílẹ̀ láàrin Ṣàngó, Aláàfin Ọ̀yọ́, àwọn olórí ogun rẹ̀ méjì, Gbọnka àti Tìmí lápa kan àti àwọn Ọ̀yọ́mèsí lápá kejì. Ìtakora tí ó díjú tí ó fara hàn núinú àhunpọ̀ ìtàn náà kò yọ Ọya ààyò ayaba Ṣàngó sílẹ̀ rárá.  Nípa títẹ̀lé ìmọ̀ràn àwọn ìjòyè rẹ̀ àti Ọya, Ṣàngó gbìyànjú láti kọ ẹ̀yìn àwọn olórí ogun rẹ̀ méjèjì síra wọn. Ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ bá ẹ̀yìn yọ Ṣàngó gan-an fúra rẹ̀ sì di ẹni yẹ̀yẹ́. Èyí mú Ṣàngó bínú àbíjù tí ó sì fi bẹ́ẹ̀ ṣekú pa púpọ̀ nínú àwọn ènìyàn rẹ̀. Nígbà tí ojú rẹ̀ wálẹ̀ ó dùn ún púpọ̀ débi wípé ó pokùn so. [Ó pọn dandan kí o lọ ka ìwé eré-onítàn *Ọbá Kò So* fún àǹfàní àra rẹ]
- Àpẹẹrẹ irú eré onítàn bẹ́ẹ̀ tí Oyin Adéjọbí kọ ni *Ìpadàbọ̀ Odùduwà, Àjàṣorò* àti *Gospel Truth*. Láti inú ìtàn ìwásẹ̀ àti ti akọni-kàyéfì ní eré oníṣe *Ìpadàbọ̀ Odùduwà* àti ti *Àjàṣorò* ti jẹ jáde. Àwọn ìtàn méjèèjì ní í ṣe pẹ̀lú ara wọn. Nínú *Ìpadàbọ̀ Odùduwà* ni a ti ṣe àfihàn bí Ọbàtálá ṣe gba ìjọba mọ́ Odùduwà lọ́wọ́ nígbà tí Odùduwà rin ìrìnàjò lọ sí òkè ọ̀rà. Ṣùgbọ́n nípa ìrànlọ́wọ́ Ọbameri, akọni olóyè mìíràn ni wọ́n fi lé Ọbàtálá àti àwọn alátìlẹyìn rẹ̀ kúrò nílùú tí Odùduwà sì padà sí orí ìtẹ́ rẹ̀.
- Àwọn ìran Ọbàtálá ni Ìgbò tí ó wá ń fi jagunjagun eégún oníko kó àwọn ará Ifẹ̀ tí ó jẹ́ ìran Odùduwà lẹ́rú nínú eré *Àjàṣorò*, Mọrèmi tí ó jẹ́ olorì Ọ̀ọ̀ni Ọ̀rànmíyàn nígbà náà ni ó lọ wádìí ọ̀rọ̀ eégún náà ní ilẹ̀ Igbo nípa fífi ẹ̀mí ara rẹ̀ wéwu, èyí sì ni wọ́n fi rí ẹ̀yìn àwọn Igbo pátápátá. Ṣùgbọ́n kí Mọrẹ̀mi tó lọ sílẹ̀ Igbo ó ti lọ jẹ́jẹ̀ẹ́ lọ́dọ̀ òrìṣà odò Ẹ̀sìnmìnrìn pé òun yóò fi ẹni tí òun bá kọ́kọ́ gán-án-ní nígbà tí òun bá padà láyọ̀ rúbọ sí i. Ọmọ rẹ̀ kan ṣoṣo tí ó ń jẹ́ Ẹ̀là ni ó kọ́kọ́ pàdé, ó sì fi rúbọ sí òrìṣà náà. Èyí ni ó mú kí eré onítàn náa jẹ́ ládojúdé.

- Kọlá Ògúmọlá náà ṣe àmúlò orísun yìí nínú *Òrìṣà Jẹ́ N Pé Méjì Obìnrin Kò dénú, Hell on Earth, Èṣù Ọ̀dàrà, Ọgbọ́n Ju Agbára* àti *Kádàrá ò papọ̀*. Ó yẹ kí á tọ́ka sí i pé fọ́n-ọ́n-rán àlọ́-onítàn náà rinlẹ̀ gan-an nínú *The Palmwine Drinkard* àti *Àdììtú Olódùmarè*, ṣùgbọ́n láti inú àwọn ìwé ìtàn àròsọ tí Ògúnmọ́lá ti fa àwọn eré náà yọ ni àbùdá náà ti wà tẹ́lẹ̀.
- Moses Ọláìyá náà ṣe eré ajẹmọ́tàn Yorùbá kan tàbí méjì. Èyí tí ó gbajúmọ̀ jù lọ ni *Abọ́bakú*, níbi tí ó ti fi àṣà kí Olóyè Ọnà ìṣokùn (Abọ́bakú) máa gba ẹ̀mí ara rẹ̀ nígbà tí Aláàfin bá wàjà ṣe ẹ̀fẹ̀. Ọdún 1944 ni ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó fi ṣeré náà wáyé ní òde Ọ̀yọ́ nígbà tí Ọba Ládìgbòlù Kejì wàjà.
- Nínú eré náà Bàbá Sàlá, tí Moses Ọláìyá Adéjùmọ̀ sín jẹ ni Abọbakú tí ó nílati gbẹ̀mí ara rẹ̀ lẹ́yìn ikú Aláàfin. Ṣùgbọn Bàbá Sàlá bẹ̀rẹ̀ sí dá oríṣiríṣi ọgbọ́n láti yẹ ikú náà. Ó kó onirúurú ìgbá àdému, àwo, páànù àti ìkòkò tí wọ́n wà ní dídé sílẹ̀, ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í ṣí lọ́kọ̀ọ̀kan. Ọmọ rẹ̀ Bándélé sì ń rọ̀ a kí ó tètè ṣí igbá.
- Ó yẹ kí á mẹ́nu bà á pé Dúró Ladipọ (nínú *Ọbá Wàjà*) àti Wọlé Ṣoyinka (nínú *Death and the King's Horseman* tí Akinwùmí Ìṣọ̀lá tùmọ̀ sí *Ikú Olókùn Ẹṣin*) náà fi ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi yìí kan náà ṣeré, ṣùgbọ̀n eré Ládojúdé ni ti àwọn méjèèjì, nígbà tí ti Moses ỌLáìyá jẹ́ aláwàdà tàbí amẹ́rìn-ín-wá.

## 5. 0 Ìsọníṣókí

- Ó yẹ kí á yán an pé eré-oníṣe tí ó dá lérí ìtàn Bíbélì, tí àwọn eléré bí Ogúnde fi bẹ̀rẹ̀ ti ń wáyé nínú àwọn ilé ìjọ́sìn àwọn ọmọlẹ́yìn Krístì kí ó tó dìgbà tí àwọn òṣèré wọ̀nyí bẹ̀rẹ̀ eré ní pẹrẹu. Kì í ṣe àwọn ilé ìjọsìn nìkan ni àwọn eré wọ̀nyí sì tí máa ń wàyé, a máa wáyé ní àwọn ilé ẹ̀kọ́ náà ní àkókò ìṣeré ìparí ọdún ní àwọ ilé ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀. Ó tún yẹ kí á mẹ́nu bà á pé lẹ́yìnọ̀rẹyìn, àwọn eléré eré-oníṣe onílànà Ogunde kò fi orísun kan ṣoṣo ṣe. Bí eré wọn ṣe ń dá lé ìtàn ìbílẹ̀ ni ó ń dá lé ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn, èyí kì í ṣe ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn ọmọlẹ́yìn Krístì nìkan mọ́. A sì tún máa dá lé orí ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ náà. Eré tí ó ń dá lérí ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ yìí ni ọ̀wọ́ eré-oníṣe onílànà Ogunde tí ó máa ń pọ̀ jùlọ títí di òní.

- Ìsọ̀rí mẹ́rin ni a pín àwọn eré-oníṣe onílànà Ogunde sí nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí nígbà tí a lo orísun àwọn eré náà gẹ́gẹ́ bí òṣùwọ̀n ìpínsísọ̀rí. Àwọn ìsọ̀rí mẹ́rẹ̀ẹ̀rin náà ni eré adáléri ìtàn Bíbélì, eré adáléri lítíréṣọ̀ mìíràn, eré adáléri ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ àti eré adáléri ìtàn Yorùbá.
- Yàtọ̀ sí Ogunde, àwọn òṣèré tí a sọ pé wọ́n gbé eré wọn ka orí ìtàn Bíbélì ni Oyin Adéjọbí, Kọ́lá Ògúnmọ́lá àti Dúró Ládiípọ̀. Àwọn wọ̀nyí náà ni a tún sọ pé wọ́n ṣe àmúlò àwọn lítíréṣọ̀ mìíràn gẹ́gẹ́ bí orísun eré wọn. Moses Ọláìyá kò ṣe irú eré-onítàn yìí ní tirẹ̀.
- A ṣe àlàyé pé Oyin Adéjọbí tẹra mọ́ àwọn eré adáléri ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́ dáradára. Kọ́lá Ògúnmọ́lá àti Dúró Ládipọ tẹra mọ́ àwọn eré adáléri ìtàn Yorùbá. Nígbà tí Dúró Ladipọ tẹra mọ́ eré adáléri ìtàn ìwáṣẹ̀, Kọ́lá Ògúnmọ́lá tẹra mọ́ eré adáléri ìtàn àlọ́.

## 6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Òṣùwọ̀n wo ni a mú lò láti pín eré-oníṣe onílànà Ogunde sí ìsọ̀rí ìsọ̀rí?
2. Dárúkọ àwọn ìsọ̀rí tí a pín eré-oníṣe onílànà Ogunde sí.
3. Ṣe àlàyé àwọn ìsọ̀rí náà ní ṣókí ṣókí kí o sì fi eré-oníṣe onílànà Ogunde méjìméjì ṣe àpẹẹrẹ ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.

## 7. 0 Ìwé ìtọ́kasí

Ladipọ, D. 1970. *Ọba Kò só*. Lagos: Macmillan and Co. Nig. Ltd.

Ladipọ, D. 1971. *Mọrèmi*. Lagos: Macmillan and Co. Nig. Ltd.

Ogundeji, P. A. 1981. The plays of Oyin Adejọbi: An Introductory Study. Àpilẹ̀kọ fún Oyè ìjìnlẹ̀ Ẹm-Eè. Department of Linguistics and African Studies, University of Ibadan, Ibadan.

Ogundeji, P. A. 1988. A Semiotic Study of Duro Ladipo's Mythico-Historical Plays, Àpilẹ̀kọ fún oyè ìjìnlẹ̀ gíga. University of Ibadan, Ibadan.

Ogundeji, P. A. 1991. "Classification and some Literary Aspects of Duro Ladipọ's Plays",

*Research in Yorùbá Language and Literature* No. 1. Ọbafẹmi Awolowo University, Ilé-Ifẹ.

Ogundeji, P. A. 1991. Friendship, House-wife Rivalry and Human Lust in the Plays of Kọ́lá Ògúnmọ́lá. LACE Occasional Publications, Ibadan.

Ògúnmọ́lá, K. 1965. *Ìfẹ́ Owó*. Mbari Mbayọ Publications, Òṣogbo.

Ògúnmálá, K. 1972. *The Palmwine Drinkard*. Institute of African Studies, University of Ibadan, Ibadan

## Ìpín 4: Ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá

### Ìlapa èrò

1\. 0 Ìfáárà

2 .0 Èròńgbà

4\. 0 Àkóónú iṣẹ́

4\. 1 Ìgbéǹde

4\. 1. 1 Akitiyan ìbẹ̀rẹ̀

4\. 1. 2 Ìgbìyànjú àkọ́kọ́

4\. 1. 3 Ìbẹ̀rẹ̀ gan-an-gan

4\. 2 Ìdàgbàsókè

4\. 0 Àgbálọgbábọ̀

5\. 0 Ìsọníṣókí

6\. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7\. 0 Ìwé ìtọ́kasí

### 1. 0 Ìfáárà

Ó yẹ kí á rán ara wa létí nípa àwọn ọ̀rọ̀ èdè ìperí mẹ́ta tí à ń mú lò lemọ́lemọ́ tí a sì ti kọ́kọ́ jíròrò lé lórí ní ìbẹ̀rẹ̀ kọ́ọ̀sì yí nínú Ìpín Kìn-ín-ní, Módù Kìn-ín-ní. Àwọn ọ̀rọ̀ èdè ìperí náà ni 'eré-onítàn' tí a fi túmọ̀ *play*, 'eré-oníṣe' tí a fi túmọ̀ *drama* àti 'tíátà' tí ó jẹ́ àyálò *theatre*. A ti pe àkíyèsí sí ìwọ̀núbọ̀nú tí ó wà láàárín ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ èdè iperí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta. A

sọ pé eré tí a fi gbé àhunpọ̀ ìtàn kalẹ̀ ni a kà sí eré-onítàn. Eré yìí le jẹ́ àpilẹ̀kọ, àdàkọ tàbí àpilẹ̀ṣe. Nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ eré-onítàn gẹ́gẹ́ bí ìlànà ẹ̀kọ́ kan ni a sọ pé a sábàá máa ń sọ̀rọ̀ nípa eré-oníṣe. Nígbà mìíràn, a le pè é ní "dírámà" (àyálò *drama*). Ohun tí ó tún máa ń fa ìlọ́júpọ̀ ni pé, àwọn eré tí a kọ sí inú ìwé, yálà àpilẹ̀kọ tàbí àdàkọ náà ni a sọ pé wọ́n tún jẹ́ eré-oníṣe. Bẹ́ẹ̀ sì ni a lè pe ti àwọn àbáláyé tí wọ́n jẹ́ àpilẹ̀ṣe pọ́nńbbélé náà ní eré-oníṣe; gbogbo wọ ló ní ìṣe nínú. Nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìṣeré lórí ìtàgé tàbí lójú agbo eré ni a sọ pé a máa ń sọ̀rọ̀ tíátà ní tirẹ̀. Bákan náà ni sọ pé a máa ń pe gbọ̀gàn tí a ti ń gbé eré kalẹ̀ fún òǹwòran láti wò náà ní tíátà. Bí a bá wo àwọn àlàyé tí a ṣe nípa àwọn ọ̀rọ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta wọ̀nyí dáadáa, a ó rí i pé ìtumọ̀ wọn wọnú ara wọn. Akitiyan láti pààlà gúnmọ́ sáàárín wọn sì nira púpọ̀púpọ̀ láti ṣe. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a óò tẹra mọ́ àmúlò eré-onítàn ní lílò nítorí pé gbogbo eré tí ó jẹ́ àpilẹ̀kọ, tí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ wa sì dá lé ni a fi gbé ìtàn kan tàbí òmíràn kalẹ̀. Èyí kò dí wa lọ́wọ́ láti ṣe àmúlò àwọn èdè ìperí méjì yòókù níbi tí ó bá ti yẹ o.

## 2. 0 Èròǹgbà

Ní opin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú ìpín yìí, o ó ti le ṣe àlàyé nípa ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè eré-onítàn àpilẹ̀kọ Yorùbá wọ̀nyí:

- Akitiyan ìpìlẹ̀.
- Ìgbìyànjú àkọ́kọ́ nínú ìwé ìròyìn.
- Ìbẹ̀rẹ̀ rẹ̀ gan-an-gan.
- Ìdàgbàsókè rẹ̀ títí di lọ́ọ́lọ́ yìí.

## 3. 0 Ìbéèrè ìṣáájú

1. Ta ni ó kọ́kọ́ gbìyànjú láti kọ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ Yorùbá, kín ni àkọlé eré rẹ̀ náà, ọ̀nà wo sì ni ó gbà gbé e jáde?
2. Kín ni àkọlé eré-onítàn àpilẹ̀kọ Yorùbá àkọ́kọ́ gan-an-gan, ta ni ó kọ ọ́, ọdún wo sì ni wọ́n gbé e jáde?
3. Dárúkọ obìrin òǹkọ̀wé eré-onítàn mẹ́ta tí o mọ̀ àti eré-onítàn tí wọ́n kọ pẹ̀lú ọdún tí wọ́n gbé àwọn eré náà jáde.

## 4. 0 Àkóónú iṣẹ́

Ìgbéǹde tàbí ìdidelẹ̀ ni a óò kọ́kọ́ jíròrò lé lórí, kí á tó bọ́ sórí ìdàgbàsókè.

## 4. 1. 0 Ìgbéǹde

- Ọ̀nà mẹ́ta tí a pín ìjíròrò sí ní ibí yìí ni akitiyan ìpìlẹ̀, ìgbìyànjú àkọ́kọ́ nínú ìwé ìròyìn àti ìbẹ̀rẹ̀ eré-onítàn àpilẹ̀kọ gan-an-gan.
- Akitiyan ìpìlẹ̀ ni gbogbo ìlàkàkà àwọn kan láti kọ eré-onítàn ṣùgbọ́n tí kò yọri sí eré-onítàn àpilẹ̀kọ nítorí pé wọn kò ní èrò ìwé eré kíkọ lọ́kàn, eré ṣíṣe ni ó jẹ wọ́n lógún. Wọ́n kàn ṣe àmúlò àkọsílẹ̀ eré-onítàn bí ohun èlò tí ó jẹ́ àtẹ̀gùn láti gbé eré kalẹ̀ lórí ìtàgé ni.
- Ìgbìyànjú àkọ́kọ́ ní tirẹ̀ ni aáyan láti kọ eré-onítàn àpilẹ̀kọ tí ó sì jẹ́ pé kíkọ eré-onítàn yìí gan-an ni àmojúsùn òǹkọ̀tàn/ òǹkọ̀wé, ṣùgbọ́n tí akitiyan náà kò kógo já nítorí àkùdé tí ó bá a, tí kò sì dé orí igbá bí odindi ìwé eré-onítàn.
- Ìbẹ̀rẹ̀ eré-onítàn àpilẹ̀kọ gan-an-gan ni ìgbà tí eré-onítàn tó kógo já gẹ́gẹ́ bí ojúlówó ìwé eré-onítàn; nígbà yẹn ni eré-onítàn àpilẹ̀kọ tó bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu.

## 4. 1. 1 Akitiyan ìpìlẹ̀

- Láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ni àwọn Yorùbá tí máa ń ṣe eré oríṣiríṣi. Oríṣi eré àdáyébáYorùbá méjì tó gbajúmọ̀ ni ọdún ìbílẹ̀ àti idán eégún aláré (Ògúndèjì, 1992, 2000). Àwọn eré yìí kì í ṣe àpilẹ̀kọ, àpilẹ̀ṣe pọ́nńbélé ni wọ́n.
- Àìmọye ni àwọn eré-oníṣe tí àwọn ọmọ ilé ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ti ṣe ní àwọn àsìkò ìṣeré ìdánilárayá (ẹntatémẹ́ǹtì) níparí ọdún, ní àkókò tí àṣà mọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà dé, ṣùgbọ́n tó jẹ́ pé kò sí àkọsílẹ̀ fún wọn.
- A tún rí lára àwọn eré oríṣìíríṣìí tí àwọn ilé ìjọsìn ọmọlẹ́yìn Krístì ti ṣe lásìkò tí wọ́n bá ń ṣe ayẹyẹ kan tàbí òmíràn, pàtàkì jù lọ lásìkò ọdún Kérésì àti ọdún Àjíǹde tàbí Ìkórè. Nígbà míràn wọn a sì máa ṣe irú àwọn eré bẹ́ẹ̀ láti fi kó owo jọ fún ìkọ́lé tàbí ohun mìíràn. Irú àwọn eré yìí sábàá máa ń dá lé ìtàn inú Bíbélì. Láti ìdí ṣíṣe irú àwọn eré bẹ́ẹ̀ ni Ogunde, Oyin Adéjọbí àti Dúró Ládipọ̀ ti dídelẹ̀ bí àpẹẹrẹ (Ògúndèjì, 1992).
- Ní ọdún 1903, D. A. Oyèdèlé kọ eré-onítàn kan tí àkọlé rẹ̀ ń jẹ́ *The King Eléjìgbò and Princess Àbẹ̀jẹ́ of Kontangora*, èyí tí Ẹgbẹ́ Ìfẹ́ ṣe lórí ìtàgé lẹ́yìnọ̀rẹyìn ní ọdún náà. Àṣeyọrí èyí ni a lérò pé ó fún Oyèdélé ní ìwúrí láti kọ eré-onítàn mìíràn tí àkọlé

rẹ̀ ń jẹ́ *the Jealous Queen Ọya of Ọ̀yọ́* ní ọdún 1905 fún Ẹgbẹ́ Ìfẹ́ kan náà láti ṣe lórí ìtàgé. Ṣíṣe lórí ìtàgé ni a lérò pé ó ṣe pàtàkì sí  Oyèdélé. Èyí ni kò jẹ́ kí ìgbé-jáde eré-onítàn tí ó kọ náà fún kíkà jẹ ẹ́ lọ́kàn.

- Akitiyan àwọn oníwèé ìròyìn, nípa bí wọ́n ṣe máa ń ṣe àtún-yẹ̀wò àti ìròyìn ohun tí ó ń lọ láwùjọ ni a ṣe ní ìmọ̀ nípa àwọn eré Yorùbá ní àsìkò ìmúnisìn àwọn Gẹ̀ẹ́sì ní ilẹ̀ Nàìjíríà. Láti ipasẹ̀ akitiyan wọn ni a ṣe gbọ́ nípa eré Oyèdélé tí a ti mẹ́nu  bà àti àwọn mìíràn bí èyí tí ẹgbẹ́ *Glee Singers* ní ìlú Èkó ṣe agbátẹrù rẹ̀ ní lọdún 1910.
- Ẹgbẹ́ *Glee Singers* gbé ìdíje eré-onítàn kíkọ àpil (àpilẹ̀kọ) kan kalẹ̀ ní ọdún 1910. Èrò wọn ni láti ṣe eré tí ó bá gbé igbá orókè ní orí ìtàgé. Eré Olympus Moore, *Aṣìkà Bí Àparò* àti ti I. B. Akínyẹlé, *Àwọn Ìwàrẹ̀fà Mẹ́fà* ló gbégbá orókè nínú gbogbo àwọn eré-onítàn tí wọ́n rí gbà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé fún gbígbé-kalẹ̀ lórí ìtàgé ni wọ́n kọ àwọn eré náà, kò ṣókùnkùn rárá pé níṣe ni wọ́n kọ́kọ́ pilẹ̀ kọ àwọn eré náà; àpilẹ̀kọ ni wọ́n.
- Nítorí pé kò sí àrídájú pé àwọn eré wọ̀nyí di gbígbé jáde lórí àtẹ ìtàwé fún kíkà àwọn ará ìlú ni a fi fi ojú akitiyan tàbí ìgbìyànjú tí kò kẹ́sẹ járí tan wò wọ́n. Àwọn akitiyan mìíràn bẹ́ẹ̀ tún le wà yàtọ̀ sí àwọn èyí tí a mẹ́nu bà, ṣùgbọ́n tó jẹ́ pé ìwádìí kò ì tí ì wú síta.

3. 1. 2 Ìgbìyànjú àkọ́kọ́ nínú ìwé ìròyìn

- Bí ó ṣe jẹ́ pé inú ìwé ìròyìn ni ewì àpilẹ̀kọ àti ìtàn àròsọ àpilẹ̀kọ ti kọ́kọ́ jẹ yọ, bákan náà ni ọ̀rọ̀ ṣe rí fún eré-onítàn Yorùbá.
- Ní ọjọ́ kẹrinlélógún, oṣù kẹta ọdún 1923, E. A. Akitan tí ó jẹ́ olóòtú ìwé ìròyìn  *Elétí Ọfẹ* bẹ̀rẹ̀ sí í gbé eré-onítàn kékeré kan jádé ní inú ìwé ìròyìn rẹ̀.  Àkọ́lé mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni ó fún eré  náà. Àwọn àkọ́lé náà ni *Rẹrin Díẹ̀*, *Pa Mi N Kú Obìnrin* àti *Ẹni Máa Kú Pàdé Ẹni Máa Pa á*. Bí Ògúnṣínà (1980, 1982, 2001) ti tọ́ka sí i, ohun tí èyí fi hàn ni ẹni tí ó kọ eré-onítàn náà ṣì ń dá a lábàá ni; kò tí ì pinnu àkọlé tí yóó lò gan-an ni pnínú mẹ́tẹ̀ẹ̀ta. Èyí ni ó jẹ́ kí á mọ̀ pé ìgbìyànjú ni kíkọ eré náà lápapọ̀ ṣì jẹ́. Ọjọ́ kẹrin, oṣù kẹrin ọdún 1923 kan náà yìí ni ó mú eré-onítàn náà wá sí òpin.

- Ògúnṣínà (1980,1982, 2001) tilẹ̀ sọ pé àhunpọ̀ ìtàn eré náà jẹ́ ti aáwọ̀ tí ó wáyé nínú ìdílé lọ́kọláyà kan. Ajíbábi ni ìyàwó ilé náà ń jẹ́, ẹni tí ọkọ rẹ̀ ní kó wá oúnjẹ fún òun kí ó tó lọ sí ibi iṣẹ́ ní kùtùkùtù. Dípò kí ìyàwó ṣe bẹ́ẹ̀, ọ̀rọ̀ burúkú ló sọ sí ọkọ rẹ̀, èyí sì di iṣu ata yá-an-yàn-an ní ẹ̀ẹ̀dẹ̀ wọn. Ajibábi, tó fún ọkọ rẹ̀ lésì kò-bákùn-gbé yìí náà ti mọ ìyà tó wà ní ìdí rẹ̀; bí ó ti ṣe ṣe báyìí tán ni ó fi ẹsẹ̀ fẹ́ ẹ. Ohun tí èyí ń tọ́ka sí ni pé irú èdè àìyedè bẹ́ẹ̀ kì í ṣe ohun tuntun nínú ìdílé náà. Àwọn ará àdúgbò ló yanjú ọ̀rọ̀ náà nígbà tí wọ́n ránńṣẹ́ pe ìyàwó ní ọjọ́rọ̀, tí wọ́n sì parí aáwọ̀ náà.
- Ògúnṣínà fi kún àlàyé rẹ̀ pé àhunpọ̀ ìtàn eré àpilẹ̀kọ kúkurú náà lọ tààrà, kò sì lọ́jú rárá. Ó ṣàfikún pé ìfìwàwẹ̀dá inú rẹ̀ kò lọ́ọ̀rìn; iṣẹ́ pàtàkì tí òǹkọ̀tàn eré-onítàn náà fẹ́ jẹ́, láti fi ipanilẹ́tìn-ín dáni lẹ́kọ̀ọ́ ní ó gbájú mọ́. Ògúnṣínà kò ṣài mẹ́nu bà á pé ìlú Èkó ni ìbùdó ìtàn eré yìí àti pé eré náà kógo já nípa ìlò èdè inú rẹ̀. Ó tilẹ̀ sọ pé ìlò èdè ni òǹkọ̀tàn fi ṣe àgbékalẹ̀ àwàdà àti ìpanilẹ́rìn-ín tí ó pegedé nínú eré náà.
- Torí pé eré yìí nìkan ni a rí àrídájú rẹ̀ ní àkókò ìgbìyànjú kíkọ eré-onítàn ni àwọn kan ṣe máa ń pe eré náà ní eré-onítàn àpilẹ̀kọ àkọ́kọ́. Ṣùgbọ́n bí a bá tẹ̀lé ìlànà tí a fi ń dá ìwé eré-onítàn mọ̀ ní pàtó, a kò le sọ pé eré náà kógo já ti a fi lè pè é ní ìwé eré-onítàn nítorí pé wọn kò sọ ọ́ di ìwé eré-onítàn láàyè ara tirẹ̀. Àgbéjáde díẹ̀díẹ̀ nínú ìwé ìròyìn láàrin ọ̀sẹ̀ méjì ni ó jẹ́; kò di odindi ìwé, ìbáà tilẹ̀ jẹ́ ìwé kékeré, kí ó sì wà fún títà lórí àtẹ ní àrọ́wọ́tó àwọn òǹkàwé.

### 3. 1. 3 Ìbẹ̀rẹ̀ eré àpilẹ̀kọ gan-an

- Lẹ́yìn ìgbìyànjú àkọ́kọ́ tí E. A. Akítán ṣe ní ọdún 1923 yìí, kò tún sí ìgbìyànjú kankan tí a mọ̀ mọ́ títí di ọdún 1946 nígbà tí eré *Pàṣán Ṣìnà* tí Adébóyè Babalọlá kọ dé orí igbá. Ìyẹn ni pé ọdún mẹ́tàlélógún (23) ni ó wà láàárin ìgbìyànjú àkọ́kọ́ àti ìgbà tí eré àkọ́kọ́ gan-an dé orí igbá fún títà fún àwọn òǹkàwé. Ọdún kejìlá lẹ́yìn ti àkọ́kọ́ yìí ni èkejì tó jáde ní ọdún 1958. J. F. Ọdúnjọ ni ó kọ ọ́, *Agbàlọ́wọ́ Mérìí Baálẹ̀ Jòǹtolo* sì ni àkọlé rẹ̀.
- *Pàṣán Ṣìnà* jẹ́ eré-onítàn tó ṣe àfihàn ìtakora láàárín àṣà ọ̀làjú òde òní àti àṣà àbínibí Yorùbá, tí àṣà ọ̀làjú bá nílẹ̀. Ní ti *Agbàlọ́wọ́mérìí, Baálẹ̀ Jòǹtolo*, eré náà ṣe àfihan

bí àwọn ọlọ̀lá, tí wọ́n di ipò àṣẹ mú ní àwùjọ ṣe máa ń fi ọwọ́ ọlá gbá àwọn ará ìlú, tí wọn kò ní agbára kankan lójú; tí wọ́n máa ń rẹ́ wọn jẹ.

- Nígbà tí wọ́n ṣàgbéjáde àwọn eré méjèèjì yìí tí ní àkókò ìṣaájú ìgbòminira orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni a le pè ní ìbẹ̀rẹ̀ kíkọ eré-onítàn àpilẹ̀kọ Yorùbá; *Pàṣán Ṣìnà* ni àkọ́kọ́, *Agbàlọ́wọ́mérìí, Baálẹ̀ Jòǹtolo* ni ìkejì. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀ fara hàn nínú àwọn eré-onítàn àpilẹ̀kọ méjèèjì.

## 3. 2 Ìdàgbàsókè

- Lẹ́yìn eré-onítàn méjèèjì yìí, eré kankan kò tún jáde mọ́ di ọdún 1964, lẹ́yìn ìgbòmìnira orílẹ̀ èdè Nàìjíríà. Ọdún yìí ni eré-onítàn kékeré kan tí àkọlé rẹ̀ ń jẹ́ *Ká Sòótọ́ Ká Kú,* tí Ọlánipẹ̀kun Ẹ̀san kọ dé orí àtẹ. Inú ìtàn ayé àtijọ́ ilẹ̀ Gíríìkì kan ni ó ti fa àhunpọ̀ ìtàn eré náà yọ. Àṣà kí á máa ṣe àyídà ìtàn lítíréṣọ̀ ilẹ̀ mìíràn pàápàá ti ilẹ̀ òkèèrè sí eré àpilẹ̀kọ Yorùbá ni Ọlánipẹ̀kun Ẹ̀san fi lọ́lẹ̀ nípasẹ̀ eré kukurú tí ó kọ náà. Eré náà sì wà lára àwọn tí ó jáde sórí àtẹ ní ẹ̀wádún (ọdún mẹ́wàá) kìn-ín-ní lẹ́yìn ìgbòmìnira Nàìjíríà.
- Láàrin ẹ̀wádún àkọ́kọ́, lẹ́yìn ìgbòmìnira Nàìjíríà yìí náà ni àwọn eré wọ̀nyí jádé: *Wọ́n Rò Pé Wèrè Ni* tí Adébáyọ̀ Fálétí kọ (1965); *Olúwa Ló Mẹjọ́ Dá* tí Afọlábí Ọlábímtan kọ (1966); *Òrékelẹ́wà* tí Ọlánipẹ̀kun Ẹ̀san kọ (1968). Ní ẹ̀wádún kìn-ín-ní lẹ́yìn ìgbòmìnira yìí náà ni a lè sọ pé eré-onítàn àpilẹ̀kọ Yorùbá bẹ̀rẹ̀ sí í gbéra sọ. Ohun kan tí ó sì fara hàn nípa àwọn eré-onítàn wọ̀nyí ni pé eré adánilẹ́kọ̀ọ́ lọ́nà tààrà ni wọn.
- Ní àwọn ọdún 1970, ìyẹn ní ẹ̀wádún kejì lẹ́yìn ìgbòminira orílẹ̀-èdè wa, akitiyan kíkọ eré-onítàn àpilẹ̀kọ bẹ̀rẹ̀ sí í fẹsẹ̀ múlẹ̀. Lára àwọn eré tí ó jáde sórí àtẹ fún àwọn òǹkàwé láti rà ní àwọn ọdún náà ni *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ (1970), *Jaiyéọlá* tí Akínṣọlá Awóṣúsì kọ (1970), *Gbékú Dè àti Iṣẹ́ Abẹ* tí S. A. Dúrójayé kọ (1970), *Ilé Tí A Fitọ́ Mọ* tí Olú Dáramọ̀lá kọ (1971), T. A. A. Ládélé *Ìgbà Ló Dé* (1971) *Ọbalúayé* tí Wálé Ògúyẹmí kọ (1972), *Baṣọ̀run Gáà,* tí Adébáyọ̀ Fálétí kọ (1972), *Ìdààmú Páàdì Mínkáílù* tí Aébáyọ̀ Fálétí kọ (1972) *Rẹ́rẹ́ Rún* tí Ọládẹ̀jọ

Òkédìjí kọ (1973), *Lísàbi Agbòǹgbò Àkàlà* tí Olú Owólabí kọ (1977) àti *Àárẹ Àgo Aríkúyẹrí* tí Láwuyì Ògúnníran (1977).

- Ní ẹ̀wádún 1970 yìí ni eré-onítàn àpilẹ̀kọ adáléri ìtàn ìṣẹ̀lẹ̀ gidi kọ́kọ́ fara hàn. Èyí ni *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*, *Baṣọrun Gáà*, *Lísàbi Agbòǹgbò Àkàlà*, *Àárẹ-Agò Aríkúyẹrí* àti *Ìgbà Ló Dé*. Bákan náà ni ó jẹ́ wí pé àkókò yí kan náà ni eré àpilẹ̀kọ afèhónú-hàn kọ́kọ́ wáyé. *Rẹ́rẹ́ Rún* sì ni eré náà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀ ti ń fara hàn nínú àwọn eré Yorùbá láti àkókò ìgbìyànjú àkọ́kọ́ àti ìbẹ̀rẹ̀ náà bí a ṣe sọ, síbẹ̀ ẹ̀wádún 1970 yìí náà ni a bẹ̀rẹ̀ sí í rí eré tí ó gbájú mọ́ ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀ gan-an, ìyẹn ni pé tí ìfẹ̀dáṣẹ̀fẹ̀ peléke nínú rẹ̀. Èyí ni eré S. A. Dúrójayé *Gbékú Dè àti Iṣẹ́ Abẹ*.
- Lááárín ẹ̀wádún 1970 – 1979 náà ni eré-onítàn àpilẹ̀kọ afèhónú-hàn àkọ́kọ́ jáde, èyí ní ọdún 1973 ní pàtó. Ọládẹ̀jọ Òkédìjí tó kọ eré *Rẹ́rẹ́ Rún* ní ọdún 1973 ló kọ́kọ́ kọ irú eré náà.
- Ní àwọn ọdún 1980 sí 1989, tí ó jẹ́ ẹ̀wádún kẹta lẹ́yìn ìgbòmìnira ni àwọn òǹkọ̀wé tuntun bí i Túnjí Ọ̀pádọ̀tun, Adémọ́lá Ọdẹ́tókun, Oyèwọlé Ògúnwálé, Jọláadé Fáladé, Oyètúnde Awóyẹlé àti Túbọ̀sún Ọládàpọ̀ náà gbé orísìírísìí àwọn ìwé eré-onítàn jáde, tí eré-onítàn àpilẹ̀kọ sì ti ń di igi àlọ́yè ní ilẹ̀ Yorùbá, tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí níí búrẹ́kẹ́ díẹ̀díẹ̀.
- Ní ẹ̀wádún 1990, tí ètò ọrọ̀ ajé ilẹ̀ Nàìjíríà kò fi bẹ́ẹ̀ dára, tí ìjọba sì ń jẹ àwọn òṣìṣẹ́ lówó ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn olùkọ́ èdè Yorùbá bẹ̀rẹ̀ sí ní í kọ àwọn ìwé Lítíréṣọ̀ Yorùbá ní orísìírísìí fún pípa owó wọlé sí àpò ara wọn; eré-onítàn àpilẹ̀kọ sì wà lára irú àwọn ìwé lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀ tí wọ́n kọ. Lára àwọn òǹkọ̀wé eré-onítàn túntun tí wọn dara pọ̀ mọ́ àwọn aṣiwájú wọn ní Láńrewájú Ọdẹàjọ̀, Tọ́pẹ Olúmúyìwá, Àkòfẹ́ Adéníyì, Adéọlá Adéníyì, Yẹmi Akínfẹ́nwá, Yẹ́misí Adébọ̀wálé, Àrìnpé Adéjùmọ̀ àti Ọlátińwọ̀ Adéagbo Fátókí.
- Láti ọdún 2000 síwájú ni àṣà kíkọ eré-onítàn ti búrẹ́kẹ́ pátápátá. Bóyá torí ìṣòro àìsíṣẹ́ tó gbilẹ̀ ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà wà lára ohun tí ó ṣe okùnfà ìbúrẹ́kẹ́ yìí. Ó yẹ kí a tẹnu mọ́ ọn pé ìbúrẹ́kẹ́ yìí ti bẹ̀rẹ̀ ní ẹ̀wádún 1980 díẹ̀díẹ̀. Lára àwọn òǹkọ̀wé eré-onítàn àpilẹ̀kọ tí ó kọ ìwé eré tuntun ní àkókò yìí ni Ọládélé Ṣàngóníyì, Akínwùmí Àtàndá, Adékúnlé Adédire, Débọ̀ Awẹ́, B. O. Dòsùnmú, Báyọ̀ Adébọ̀, Ọládiipọ̀

Ajíbóyè, Lékan Babatúndé, Ọ̀tún Rasheed, Olúṣayọ̀ Oyèríndé, Gbádé Akíntókun, Báyọ̀ Adéràntí, Olúṣọlá Àṣàmú. Kíyèsi pe àwọn tí wọ́n ti bẹ̀rẹ̀ sí í kọ ìwé eré tẹ̀lẹ̀tẹ̀lẹ̀ kò dẹ́kun láti máa kọ ìwé eré-onítàn tuntun tuntun sí i ní àsìkò yìí.

- Ìwọ̀nba péréte ni àwọn òǹkọ̀wé eré-onítàn tí wọ́n jẹ́ Obìnrin lára àwọn òǹkọ̀wé eré onítàn náà. Obìnrin àkọ́kọ́ tí ó hàn sí wa, tí ó kọ eré-onítàn àpilẹ̀kọ ni Jọláadé Fáwálé tí ó kọ *Kúṣoró*. Lẹ́yìn náà ni Olúyẹ́misí Adébọ̀wálé tí ó kọ *O Ṣèyí Tán* (1995) àti Arìnpé Adéjùmọ̀ tí ó kọ *Ẹyin Àparò* (1998). Lẹ́yìn àwọn aṣíwájú mẹ́ta yìí a tún ti rí Fadékẹ́mi Adágbádá (2009) tí ó kọ *Oníyangí*.

## 5. 0 Ìsọníṣọ́kí

Nínú àwọn lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ Yorùbá yòókù, eré-onítàn nìkan ni ó pẹ́ ju kí ó tó dídelẹ̀ ìdàgbà sókè rẹ̀ náà sì lọ́ tìkọ̀ pẹ̀lú. Bóyá àṣà ìseré Onílànà Ogunde tí ó ti gbajúmọ̀ tẹ́lẹ̀ ni kò jẹ́ kí wọ́n tètè kọ bíara sí i. Nígbà tí àwọn olùkọ́ èdè, àṣà àti lítíréṣọ̀ Yorùbá bẹ̀rẹ̀ sí ní í pọ̀ sí i tí wọ́n sì ní ìpèníjà àìrówó oṣù gbà lásìkò ni eré-onítàn àpilẹ̀kọ tó di igi àlọ́yè dáradára.

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ṣe àgbéyẹ̀wò ìgbéǹde àti ìdàgbàsókè eré-onítàn àpilẹ̀kọ Yorùbá.

- A pín ìgbéǹde náà sí: akitiyan ìpìlẹ̀, ìgbìyànjú àkọ́kọ́ àti ìbẹ̀rẹ̀ gan-an.
- Eré Olympus Moore àti ti I. B. Akínyẹlé ni a jíròrò lé lórí gẹ́gẹ́ bí akitiyan ìpìlẹ̀. Eré E. A. Akintan, *Ẹni Máá Kú Pàdé Ẹni Máa Pà á* tó jade nínú ìwé ìròyìn *Elétí Ọfẹ* ni a sọ pé ó jẹ́ ìgbìyànjú tàbí ìtiraka àkọ́kọ́.
- *Pàṣán Ṣìnà àti Agbàlọ́wọ́ Mérìí Baálẹ̀ Jòǹtolo* ni a sọ pé wọ́n jẹ́ ìbẹ̀rẹ̀ eré-onítàn kíkọ gan-an ní pàtó.
- Lábẹ́ ìdàgbàsókè ni a ti jíròrò lórí eré tó jáde láàárín àwọn ẹ̀wádún 1960, 1970, 1980 àti 1990. Ọdún 2000 títí di àkókò yìí ni á ṣàlàyé pé ó jẹ́ ojúlówó àkókò ìbúrẹ́kẹ́ eré-onítàn àpilẹ̀kọ Yorùbá.
- Bí a bá rí àwọn ẹ̀wádún méjì àkọ́kọ́ lẹ́yìn ìgbòmìnira bí àkókò fífi ìpìlẹ̀ lélẹ̀, a óò rí àkókò ẹ̀wádún méjì tí ó tẹ̀lé wọn ní ṣísẹ̀ntẹ̀lé gẹ́gẹ́ bí èyí tí wọ́n ti mọ lé ìpìlẹ̀ náà.

## 6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ta ni D. A. Oyèdélé? Ní ṣókí sọ akitiyan ìgbiyànjú rẹ̀ nígbà ìpílẹ̀ eré-onítàn àpilẹ̀kọ Yorùbá.
2. Ní ṣókí ṣe àlàyé ipa tí ìwé ìròyìn kó nínú ìgbéǹde eré-onítàn àpilẹ̀kọ Yorùbá?
3. Irú eré wo ni àwọn tí ó kọ́kọ́ kọ eré-oníṣe àpilẹ̀kọ kọ?
4. Ǹjẹ́ lóòtọ́ ni pé lẹ́yìn ìgbòmìnira Nàìjíríà ni eré-onítàn àpilẹ̀kọ to bẹ̀rẹ̀ sí í dàgbà sókè? Kọ àròkọ kékeré kan láti fi èrò rẹ hàn.

## 7. 0 Ìwé ìtọ́kasí

Ogundeji, P. A. 1992. *Yorùbá Drama I.* Ìbàdàn External Studies Programme, University of Ibadan, Ibadan.

Ogundeji, P. A. Ogundeji, P. A. 1992b. *Introduction to Yorùbá Written Literature*. Distance Learning Centre, University of Ibadan, Ibadan

Ogundeji, P. A. 2000. *Ritual as Theatre, Theatre as Ritual: The Nigerian Example*. Ìbàdàn Cultural Studies Group, Ìbàdàn.

Ògúndèjì P. A. 2014 Yorùbá Drama in Time Perspective Ìbàdàn University Press, Ibaàdàn

Ògúnṣínà, B. 1980. "Ipa tí àwọn Ìwé Ìròyìn Yorùbá Àtijọ́ Kó nínú Ìdàgbasókè Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá", *Yorùbá Gbòde: Ìwé Àtìgbàdégbà Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè Yorùbá, ilẹ̀ Nàìjíríà,* no. 5, o.i. 37-55.

Ògúnṣínà, B. 1982. "*Pa Mí N Kú Obìnrin*": An Early Attempt at Yorùbá Play Writing, *Nigeria Magazine*, no. 143, o.i. 28-32.

Ògúnṣínà, B. 2001. 'Ìdìde àti Ìdàgbàsókè Lítíréṣọ̀ Àpilẹ̀kọ Yorùbá', nínú Bádé Àjàyí (olóòtú), *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá – Èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà*, Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ Ẹ̀dá Èdè àti Èdè Nàìjíríà. Yunifásítì Ìlọrin, Ìlọrin.

Ìpín 6: Ìjẹyọ eré-oníṣe àbáláyé nínú tòde òní

Ìlapa èrò


1. 0 Ìfáárà

2. 0 Èròńgbà

3. 0 Ìbéèrè ìṣaájú

4. 0 Àkóónú iṣẹ́

4. 1. 0 Ìjẹyọ eré-onítàn àbáláyé nínú tòde òní

4. 1. 1 Ìjẹyọ ajẹmáhùnpọ̀ ìtàn

4. 1. 2 Ìjẹyọ ajẹmámójúsùn àtajẹmọ́kókó-ọ̀rọ̀

4. 1. 3 Ìjẹyọ ajẹmọ́bi ìṣeré àtibùdó-ìtàn

4. 1. 4 Ìjẹyọ ajẹmẹ́dàá ìtàn àti ìfìwàwẹ̀dá

4. 1. 5 Ìjẹyọ ajẹmọ́lò èdè

5. 0 Ìsọníṣókí

6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7. 0 Ìwé ìtọ́kasí


## 1. 0 Ìfáárà

Bí o kò bá gbàgbé ẹ̀kọ́ àtẹ̀yìnwá, ọ̀nà méjì gbígbòòrò tí a pín eré-oníṣe Yorùbá sí ni ti àbáláyé àti ti òde òní. Eré-oníṣe àbáláyé ni a tún tún pín sí ọdún ìbílẹ̀ àti idán eégún aláré. Bákan náà ni a pín eré-oníṣe tòde òní sí eré-oníṣe onílànà Ogunde àti eré-oníṣe àpilẹ̀kọ. Ohun tí a fẹ́ pe àkíyèsí sí ninú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú ìpín yìí ni pé àwọn eré-oníṣe tí a pè ní tàtijọ́ wọ̀nyi máa jẹ yọ nínú èyí tòde òní. Ọ̀nà tí àwọn eré-oníṣe àbáláyé wọ̀nyí máa ń gbà jẹyọ nínú ti òde òní náà ni a fẹ́ gbé yẹ̀wò. Lópin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó ti le ṣe àlàyé nípa àwọn ọ̀nà tí a tò sísàlẹ̀ wọ̀nyí, tí àwọn eré-oníṣe àbáláyé Yorùbá máa ń gbà jẹ yọ nínú eré-oníṣe òde òní: ọ̀nà ìjẹyọ ti

- ajẹmámùúlò ìtàn ìwáṣẹ̀ fún ìhunpọ̀-ìtàn,
- ajẹmámójúsùn àti ajèmọ́ kókó ọ̀rọ̀,
- ajẹmọ́bi ìṣeré àtibùdó ìtàn,
- ajẹmẹ́dàá ìtàn àtìfìwàwẹ̀dá àti

- ajẹmámùúlò èdè.

## 3. 0 Ìbéèrè ìṣaájú

1. Ní ṣókí ṣe àlàyé ìpínsísọ̀rí eré-oníṣe Yorùbá.
2. Kín ni ìyàtọ̀ láàrin eré-oníṣe àdàkọ àti àpilẹ̀kọ?
3. Dárúkọ àkọlé àwọn eré-onítàn òde òní mẹ́rin tí wọ́n ṣe ṣaájú kí Ogunde tó bẹ̀rẹ̀ eré ṣíṣe.

## 4. 0 Àkóónú iṣẹ́

### 4. 1. 0 Ìjẹyọ eré-onítàn àbáláyé nínú tòde òní

- Bí ìránilétí iṣẹ́ àtẹ̀yìn wá, ó yẹ kí á ṣe àlàyé pé, eré-oníṣe àbáláyé ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ pàtàkì fún eré-oníṣe òde òní. Ohun tí ó mú èyí rí bẹ́ẹ̀ ni pé kí àwọn òyìnbó amúnisìn tó dé, àti kí díẹ̀ nínú àwọn ènìyàn Yorùbá tí a kó lẹ́rú lọ sí àwọn orílẹ̀ èdè Gúsù ilẹ̀ Amẹ́ríkà tó darí padà wá sí ilẹ̀ baba wọn ni àwọn Yorùbá ti ń ṣe eré-oníṣe lóríṣiríṣi, a ti sọ èyí tẹ́lẹ̀. Àwọn eré wọ̀nyí ni a pè ní eré-oníṣe àbàláyé. Àpilẹ̀ṣe pọ́nńbélé ni wọ́n. Ọ̀nà méjì ni a sọ pé a pín àwọn eré yìí sí: ọdún ìbílẹ̀ àti eégún aláré.
- Nígbà tí àwọn ènìyàn dúdú tí wọ́n ti oko ẹrú padà dé sí ilẹ̀ Yorùbá kó àṣà ìlànà ìṣeré ilẹ̀ Yúróòpù dé, àṣà ìṣeré-oníṣe tún gba ọ̀nà ọ̀tun yọ. Àṣà ìṣeré-oníṣe tí wọ́n kó dé yìí ni a pè ní ti òde òní. Méjì tí a sì tún òun náà pín sí ni tonílànà Ogunde àti tonítàn-àpilẹ̀kọ.
- Torí pé àwọn ọmọ Yorùbá tí a ti kó lẹ́rú, tí wọ́n sì ti padà sí ilẹ̀ abínibí wọn kò fẹ́ láti sọ ọrọ̀ àṣà ìbílẹ̀ wọn nù, wọ́n fẹ́ máa gbé e lárugẹ, wọn kò fẹ́ pàdánù àwọn ogún ìbí wọn fún ti ilẹ̀ òkèèrè, èyí ni ó ṣokùnfà kí wọ́n máa fi àwọn fọ́n-ọn-rán/ ọmọlẹ̀ inú àṣà ìbílẹ̀ wọn ṣe àwọn eré tí wọ̀n mú bọ̀ láti ilẹ̀ òkèèrè níbi ti wọ́n kó wọn lẹ́rú lọ tẹ́lẹ̀. Èyí sì ni a le pè ní ìpìlẹ̀ bí eré-oníṣe àbáláyé ṣe ń jẹ yọ nínú eré-oníṣe òde òní. Àlàyé tí a ṣe sẹ́yìn nípa àwọn eré *The King Eléjìgbò and Princess Àbẹ̀jẹ́ of Kòǹtàgòrá, The Jealous Queen Ọya of Ọ̀yọ́, Aṣìkà bí Àparò*, àti *Àwọn Ìwàrẹ̀fà Mẹ́fà*, jẹ́ ẹ̀rí tó fìdí eléyìí múlẹ̀.
- A rí nínú àwọn orúkọ tí àwọn onímọ̀ fi pe àwọn eléré onílànà Ogunde yìí tó ń tọ́ka sí ìjẹyọ eré-oníṣe àbáláyé nínú ti òde oní. Àpẹẹrẹ ni irú orúkọ bẹ́ẹ̀ ni "Eré Ìbílẹ̀

Oníjó-lórin”, “Tíátà òde òní mọ̀ tàbáláyé” tí Ògúnbíyìí (1981) pè é. Ohun tí àwọn orúkọ yìí ń tọ́ka sí ni pé àbùdá eré-oníṣe àbáláyé ń fara hàn nínú eré-oníṣe òde òní.

- Àwọn ọ̀nà tí a óò jíròrò lé lórí gẹ́gẹ́ bí àwọn ọ̀nà tí eré-oníṣe àbáláyé ń gbà fara hàn nínú eré-oníṣe òde òní ni ìjẹyọ ajẹmáhùnpọ̀ ìtàn, ajẹmọ́-kókó ọ̀rọ̀, ìjẹyọ ajẹmọ́bi ìṣeré/ ibùdó ìtàn, ìjẹyọ ajẹmẹ́dàá ìtàn àti ìfìwàwẹ̀dá/ ìsínjẹ àti ìjẹyọ ajẹmọ́lò-èdè

## 4. 1. 1 Ìjẹyọ ajẹmáhùnpọ̀-ìtàn

- Ohun tí a fẹ́ kí ó yéni ní ìhín ni pé, ìtàn ìwáṣẹ̀ tí ó wà nínú àwọn eré-oníṣe àbáláyé máa ń jẹ yọ nínú àhunpọ̀ ìtàn àwọn eré-oníṣe òde òní; yálà ti onílànà Ogunde tàbí tónítàn-àpilẹ̀kọ. Èyí a máa wáyé nígbà tí olùṣẹ̀dá eré-oníṣe òde òní kan bá fi ìtàn ìwáṣẹ̀ tí ó rọ̀ mọ́ ọdún ìbílẹ̀ kan tàbí òmíràn ṣe àtẹ̀gùn àhunpọ̀-ìtàn eré-onítàn rẹ̀; yálà ti onílànà Ogunde tàbí ti àpilẹ̀kọ. Àwọn olùṣẹ̀dá eré/ òǹkọ̀tàn eré a máa ṣe èyí nípa ṣíṣe àyídà (àyípadà) ìtàn ìwáṣẹ̀ náà.
- Adédèjì (1972) àti Ògúndèjì, (1991, 1992) ti mẹ́nu bà á pé ìtàn ìwáṣẹ̀ tí ó ṣàfihàn ìtakora/ ìjà ààrin àwọn ìran Odùduwà (Ilé Ifẹ̀) àti àwọn ìran Ọbàtálá, (Ùgbò) ni ó máa ń jẹ yọ nínú ọdún Edì/ Mọ́rèmí àti nínú Ọdún Ọbàtálá.
- Ìwà akínkanjú Mọ́rèmí hàn gbangba nínú ìtàn ìwáṣẹ̀ náà. Ìtàn yìí ni àwọn onímọ̀ náà ṣe àlàyé pé ìsínjẹ ìjàkadì tí ó máa ń wáyé nínú ọdún Edì, lááàrín olóyè Ọbaláàyán àti Ọbalúfẹ̀ ń tọ́ka sí nínu ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ náà. Wọ́n tún sọ pé nínú ọdún Ọbàtálá ní Ẹdẹ, irú ìsínjẹ ìjàkadì tí ó ní ìtumọ̀ kan náà yí máa ń wáyé láàrin àwọn abọrẹ̀ méjì; Olúuwin àti Ajagẹmọ.
- Olúuwin tí wọ́n ní ó borí nínú ìsínjẹ ìjàkadì náà, tí ó sì mú Ajagẹmọ ní ìgbèkùn ni wọ́n sọ pé ó dúró fún ìran Ọbàtálá/ Ìgbò, nígbà tí wọ́n ní Ajagẹmọ tí wọ́n mú nígbèkùn dúró fún ìran Odùduwà/ Ifẹ̀. Tìmì ni wọ́n ló san owó ìtanràn Ajagẹmọ fún Olúuwin, kí ó tó dá Ajagẹmọ sílẹ̀.
- Gẹ́gẹ́ bí àlàyé àwọn onímọ̀ náà, èyí ni ó fà á ti a fi le rí Tìmì gẹ́gẹ́ bí aṣèsínjẹ Mọrèmi nínú ìṣeré náà tí owó ìtanràn tí Tìmì san yìí sì fi lè dúró bí àmì tí ó dúró fún Olúorogbo/ Ẹ̀là. Ọmọ bíbí Mọrèmí ni Olúorogbo tàbí Ẹ̀là. Ó fi ọmọ rẹ̀ kan ṣoṣo yìí jẹ́jẹ̀ẹ́ lọ́dọ̀ òrìṣà odò Ẹ̀sìnmìrìn pé òun ó fi rúbọ sí i, tí òún bá lọ ilẹ̀ Ùgbò tí òún fẹ́ ti

lọ ṣe alamí ní àlọbọ́ láti lọ wádìí àwọn Imalẹ̀ tí wọ́n wá ń kó àwọn lẹ́rú àti ẹrù nigbà gbogbo.  Ó sì mú ẹ̀jẹ́ náà ṣẹ nítorí ó lọ oko alamí náà ní àlọbọ̀. Olúorogbo ni ó dúró bí ẹni tí a fi ẹ̀mí rẹ̀ tanràn náà. Arubi tàbí òjìyà ni; ẹni tí ó ru ibi lọ tàbí tí ó jìyà fún gbogbo ìlú kí àlàáfíà lè wà.

- Àwọn eléré oníṣe òde òní kan ti ṣe àmúlò ìtàn ìwáṣẹ̀ yìí náà nínú ìgbéré oníṣe wọn kalẹ̀. Ìtàn yìí ni Dúró Ladipọ̀ fi ṣe àtẹ̀gùn eré-oníṣe rẹ̀ tó pè ní *Mọrèmi*. Ìtàn yí kan náà ni Oyin Adéjọbí ṣàmúlò nínú àhunpọ̀ *Ìpadàbọ̀ Odùduwà* àti *Àjàṣorò*. Àhunpọ̀ ìtàn Oyin Adéjọbí méjèèjì ṣàfihàn ìtakora inú ìtàn ìwáṣẹ̀ náà níbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ láàrin Odùduwà àti Ọbàtálá, nínú *Ìpadàbọ̀ Odùduwà* kí ó tó wá ṣàgbékalẹ̀ ìtakora àárín ìran àwọn Babańla méjì náà bí ó ti fara hàn nínú ìtàn ìwáṣẹ̀ Mọ́rèmí, èyí tí ó yídà sí àhunpọ̀ ìtàn eré rẹ̀, *Àjàṣorò*. A lè fi ojú eré-oníṣe abèjì/ oníbejì wo àwọn eré Oyin Adéjọbí méjèèjì náà nítorí àhunpọ̀ ìtàn wọn ní àjọṣepọ̀ típẹ́típẹ́.  Kíyèsí i pé wọ́n ṣe àdàkọ eré *Mọ́rèmí* sínú ìwé, ó sì wà lórí àtẹ fún ìgbà pípẹ́; ilé iṣẹ́ ìtẹ̀wésíta Longman ni ó gbé e jáde . Àwọn eré mẹ́tẹ̀ẹ̀ta sì ni wọ́n ṣe lórí ìtàgé àti sí orí ìwé eré onífọ́tò *Atọ́ka*.
- Oríṣiríṣi ni ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ àwọn òrìṣà tí a máa ń ṣe ọdún wọn tí àwọn eléré onílànà Ògúndé àti òǹkọ̀wé eré-onítàn àpilẹ̀kọ ti mú lò nínú akitiyan ìgbéré oníṣe wọn kalẹ̀. Dúró Ladipọ ni a sọ pé ó múra sí ṣíṣe eléyìí ju àwọn yòókù rẹ̀ lọ. Lára irú àwọn eré rẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni *Ọba Kò So*, *Ọ̀ṣun*, *Ọbàtálá,* àti *Ọ̀rúnmìlà* jẹ́.
- Ọládẹ̀jọ Òkédìjí pàápàá ṣe àyídà ìtàn ìwáṣẹ̀ kan nípa Ṣàngó sí eré àpilẹ̀kọ rẹ̀, tí ó pè ní *Ṣàngó*. Ọlátubọ̀sún Ọládàpọ̀ sì ṣe àyídà ìtàn ìwáṣẹ̀ Ògún kan sí eré-onítàn *Ògún Lákáayé*. Akínwùmí Ìṣọ̀lá náà kò gbẹ́yìn nínú kíkọ irú eré ajẹmọ́tàn ìwáṣẹ̀ bẹ́ẹ̀.  Ọ ṣe àyídà ìtàn ìwáṣẹ̀ kan nípa ìtakora àárín Ṣàngó àti Ògún nítorí Ọya nínú eré-onítàn àpilẹ̀kọ rẹ̀ tí ó fún ní àkọlé *Belly Bellows/ Oníkùn Ẹwìrì.*

4. 1. 2 Ìjẹyọ àjẹmámòòjúsùn àti ajẹmọ́-kókó-ọ̀rọ̀

- Àwọn ìdí pàtàkì pàtàkì, àyọrísí tàbí èròǹgbà tí ó wà lẹ̀yìn ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ ni a pè ní amójúsùn ní ibi. Àwọn ni a lè fi wé kókó ọ̀rọ̀, nínú àwọn eré-onítàn òde òní.
- Kókó-ọ̀rọ̀ ni òye ọ̀rọ̀, ẹ̀kọ́ tàbí láàréjà inú àwọn eré-oníṣe òde-òní. Àwọn eléré-oníṣe òde-òní a máa mú kókó ọ̀rọ̀ inú eré-oníṣe wọn láti inú eré-oníṣe àbáláyé ní ọ̀pọ̀ ìgbà.

- Ìdí tí a fi fi kókó ọ̀rọ̀ inú àwọn eré-onítàn òde òní wé àmójúsùn àwọn eré-oníṣe àbáláyé, pàápàá àwọn tí ó jẹ mórò kan tàbí òmíràn àti ọdún ìbílẹ̀ ni pé ìtáyé-ṣe ni méjèèjì wà fún.
- Pàtàkì lára àwọn àmójúsùn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún ìbílẹ̀ ni kí ìlú tòrò, kó tùbà tuṣẹ, kí ó rọ igbá ilé kó rọ àwo ọ̀dẹ̀dẹ̀, kí àlàáfíà ó sì wà; kí tara ile tará oko ó lè fẹ̀dọ̀ lérí òrónro.
- Àwọn ìṣeré ajẹmórò inú ọdún ìbílẹ̀ bí i ti ìfọ̀lú-mọ́, ìfìkà-ṣẹ̀sín, ìrubi-lọ ni wọ́n fi máa ń jíṣẹ ìtáyé-ṣe. Ìtáyé-ṣe náà ni àwọn eré ajẹmọ́wà ìbàjẹ́ láwùjọ tí àwọn eléégún aláré máa ń ṣe wà fún. Àpẹẹrẹ tí a ti tọ́ka sí ṣaájú ni idán ọ̀falè àti aṣẹ́wó pẹ̀lú tọ̀mùtí para. Wọ́n ń fi àwọn eré náà bu ẹnu àtẹ́ lu àwọn ìwà àìdára tí ó lè ba ìlú jẹ́ ni, kí àwọn ará ìlú lè máa yàgò fún irú ìwà burúkú bẹ́ẹ̀,
- Bákan náà ni ọ̀rọ̀ rí nínú púpọ̀ àwọn eré òde òní tí àwọn eléré onílànà Ogúndé máa ń ṣe àti èyí tí àwọn ònkọ̀wé eré-onítàn òde-òní máa ń kọ. Wọ́n máa ń bu ẹnu àtẹ́ lu àwọn òṣebi nítorí ìwà àìdára tí wọ́n hù. Bí àpẹẹrẹ nínú eré *Èkùrọ́ Ọlọ́jà* tí Oyin Adéjọbí ṣe, wọ́n bu ẹnu àtẹ́ lu Làágbé àti ìyàwó rẹ̀ Díẹ̀kọ̀lá pẹ̀lú Olóyè Àró tí wọ́n ń fẹ́ fi ọ̀nà èrú já òyè oba ìlú gbà fún Làágbé. Làágbé tí àwọn aṣebí náà sì fẹ́ kí oyè náà bọ́ sí lọ́wọ́ kò rí oyè náà jẹ níparí. Bákán náà ni nínú eré onítàn àpilẹ̀kọ *Baṣọ̀run Gáà* tí Adébáyọ̀ Fálétí kọ, *Àárẹ Àgò Aríkúyẹrí* tí Láwuyì Ògúnníran kọ àti *Ẹfúnṣetán Aníwúrà* tí Akíwùmí Ìṣọ̀lá kọ, wọ́n bu ẹnu àtẹ́ lu Baṣọ̀run Gáà àti Àárẹ Ògúnrìndé Ajé, Ìyálóde Ẹfúnṣetán tí wọ́n jẹ́ olóyè ìlú ṣùgbọ́n tí wọ́n ń lo agbárá ní ìlòlkulò. Ikú èṣín ni ó gbẹ̀yìn Gáà àti Ẹfúnṣetán nígbà , tí Ògunrìndé Ajé sá kúrò nílùú kí ó má baà kú. Wọ́n sọ nípa Gáà àti Ẹfunṣetán pé “Bó o láyà o ṣìkà, bó o rántí ikú Gáà/ Ẹfúnṣetán o ṣòótọ́.”  Wọ́n sì ń fi Ògúnrìndé Ajé ṣe  ẹlẹ́yà pá Aríkúyẹrí ni, kì í ṣe akọni tí ó ń pera rẹ̀.  Èyí fi hàn pé ẹni ẹ̀tẹ́ àti àbùkù ni àwọn èdá ìtàn náà, wọn kì í ṣe ẹni àpọ́nlé tí a lè fi ṣe àwòkọ́ṣe.
- Ọ̀nà ìtáyéṣe mìíràn nínú àwọn eré àbáláyé ni kíkan sáárá sí àti ṣiṣe àpọ́nlé àwọn akínkanjú àti ẹni rere. Púpọ̀ nínú àwọn ọdún ìbílẹ̀ ni ó jẹ́ pé láti fi kan sáárá sí àwọn akọni ayé àtijọ́ bí i òrìṣà àti àwọn baba ńlá pẹ̀lú àwọn ìyá ńlá ni a dá wọn sílẹ̀ fún. Àpẹẹrẹ ni ti Mọ́rèmí ni ìlé Ifẹ̀ pẹ̀lú àwọn òrìṣà bí i Ọ̀ṣun, Ọya, Ṣàngó, Ọbàtálá, Ògún, Ọ̀rúnmìlà, Àtàgé ọlọ́mú orù (òrìṣà Òkè Ìbàdàn) àti (Ọ̀rọ́sẹ̀n, orìṣà ọdún Igogo ní Ọ̀wọ̀).

- Kò sí àní àní pé àwon eléré onítàn àpilẹ̀kọ tí ó bá ṣe àmúlò ìtàn ìwáṣẹ̀ kan fún àhunpọ̀ ìtàn rẹ̀ yóò ṣe àmúlò kókó ọ̀rọ̀ láti inú ìtàn ìwáṣẹ̀ náà. Ọ̀rọ̀ ìfira ẹni jìn àti ìfẹ́ ìlú baba ẹni ti ó hànde nínú eré-onítàn *Mọ́rèmí* jẹ jáde láti inú ìtàn ìwáṣẹ̀ àti ọdún ìbílẹ̀ tí eré náà dá lé ni.
- Yàtọ̀ sí èyí púpọ̀ àwọn eléré onítàn àpilẹ̀kọ ní í máa ṣe àpọ́nlé àwọnn aṣerere nínú àhunpọ̀ ìtàn wọn nípa mímú kí ìgbẹ̀yìn wọn dára. Eléyìí fara hàn nínú eré-onítàn àpilẹ̀kọ J. F. Ọdúnjọ *Agbàlọ́wọ́mérìí: Baálẹ̀ Jòǹtolo.*
- Àkíyèsí kìn-ín-ní tí a kò gbọdọ̀ má ṣe ni pé àwùjọ Yorùbá kan náà ni irúfẹ́ eré-oníṣe méjèèjì; tàbáláyé àti tòde òní dá lé. Èyí ni a lérò pé ó fà á tí àmójúsùn àti kókó ọ̀rọ̀ inú wọn fi bára mu; tí ti àbáláyé fi ń jẹyọ nínú tòde òní. Àkíyèsí kejì ni wí pé kò sí ìgbà tí kókó ọ̀rọ̀ tí ó bá ti jẹ mọ́ ìtáyé-ṣe kò bá mu; ìbáà ṣe ayé àtijọ tàbí àkókò bágbà-mú.

## 4. 1. 3 Ìjẹyọ ajẹmọ́bi ìṣeré àtibùdó-ìtàn

- Ibi ìṣeré ni ààyè tàbí ibi gidi lójú ayé tí àwọn òǹworàn ti máa ń gbé eré kalẹ̀ fún àwọn òǹwòran láti wò. Ó lè jẹ́ olójúkorojú níbi tí àwọn òṣèré àti òǹwòrán ti lè fi ojú rinjú (ní ojú agbo eré, gbọ̀ngàn ìṣeré tàbí tíátà). Ó sì lè jẹ́ ti àijólójúkojú níbi tí ó jẹ́ pé àwòrán òṣèré alèrìn (nínú tẹlifiṣàn, fíìmù/ fídíò àgbéiéwò) tàbí ti àìlèrìn (nínú ìwé eré onífọtò) nìkan ni wọ́n lè rí. A ti ṣe àlàyé nípa èyí tẹ̀lẹ̀.
- Ibùdó ìtàn ni ààyè tí ìṣẹ̀lẹ̀ inú àhunpọ̀ ìtàn ti ṣẹ̀lẹ̀. Èyí kì í ṣe ààyè gidi lójú ayé, ti inú àhunpọ̀ ìtàn ni, ṣùgbọ́n àwọn eléré máa ń lo oríṣiríṣi ọgbọ́n ọnà alátinúdá ajẹmọ́ ìṣeré láti ṣàgbékaklẹ̀ rẹ̀ níbi ìṣeré.
- Nítorí pe agbéréká ni àwọn eléré onílànà Ogunde, ó rọrùn fún wọn láti ṣé àmúlò irú àwọn ibi ìṣeré kan náà pẹ̀lú àwọn eléégún aláré tí àwọn náà ti jẹ́ agbéréká ṣaájú wọn. Ìdí nìyí tí irú ibi ìṣeré àwọn eléégún aláré fi jeyọ nínú ìṣeré àwọn onílànà Ogunde.
- Àpẹẹrẹ irú ibi ìṣeré tí àwọn eléégún aláré máa ń lò tí ó jẹyọ niú ìṣeré àwọn onílànà Ogunde ni ojú ọjà, pàápàá nígbà tí ọjà bá ti tú àti gbàgede ìta ààfin ọba tàbí tìjòyè, ojúde agboolé kan tàbí òmíràn.

- Oríṣiríṣi ni ibi ìṣeré tí àwọn ọlọ́dún ìbílẹ̀ ti í máa ṣeré ajẹmórò wọn. Ó lè jẹ́ ojú ọjà, nígbà tí ọjà bá tú tàbí ibi tí a yà sọ́tọ̀ kan tàbí òmíràn, ojúbọ òrìṣà, inú ilé tàbí àgbàlá ilé òrìṣà, òpópónà, igbórò (bí i igbó ìgbàlẹ̀ fún ọdún eégún tàbí igbódù fún ọdún Ifá) abbl.
- Àtàwọn eléré Onílànà Ogunde àtàwọn òǹkọ̀wé eré-onítàn òde òní ní í máa ṣe àmúlò àwọn ààyè tí a dárúkọ wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí ibùdó ìtàn inú eré wọn. Èyí kò yẹ kí ó yà wá lẹ́nu nítorí gbogbo ààyè tí ó bá ti wà láwùjọ Yorùbá ni àwọn eléré náà ní àǹfààní láti fi àwòrán rẹ̀ hàn nínú eré-onítàn wọn gẹ́gẹ́ bí àwògbè tàbí díígí ti máa ń fi àwòrán ènìyàn àti nǹkan hàn.
- Bí àpẹẹrẹ, ìta gbangba ilé rẹ̀ ni Ààrẹ-Àgò Ajé ti bọ orí rẹ̀ nínú àhunpọ̀ ìtàn eré *Ààrẹ Àgò Aríkúyẹrí*. Irú orò ṣíṣe tí í máa wáyé ní àkókò ọdun ìbílẹ̀ ni orí bíbọ yìí jẹ́.
- Nínú ọ̀pọ̀ eré onílànà Ogunde àti àwọn eré àpilẹ̀kọ Yorùbá ni a ti máa ń rí àmúlò ojú ọjà gbàgede tàbí igbórò gẹ́gẹ́ bí ibùdó ìtàn. Bí àpẹẹrẹ ojú ọjà Akẹ̀sán ni àtúnjà ìjà àárín Gbọ̀nńkà àti Tìmì ti wáyé, tí Gbọ̀n-nọ́nkà sì ti fi Ṣàngó ṣẹ̀sín kí ó tó ní kí ó jáde kúrò ní Ọ̀yọ́ fún òun nínú eré *Ọba Kò So* látọwọ́ Dúró Ladipọ̀. Ojú ọjà Ifẹ̀ ni àwọn jagunjagun Ìgbò ti kó àwọn Ifẹ̀ lẹ́rú nínú eré *Mọ́rèmí* látọwọ́ Dúró Ladipọ̀ bákan náà. (Ogundeji, 1988). Nínú eré-onítàn àpilẹ̀kọ *Agbàlọ́wọ́mérìí:Baálẹ̀ Jòǹtolo*, ojú ọjà ni àwọn ará ìlú ti kọ Àkẹ́jù gẹ́gẹ́ bí i Baálẹ̀ lẹ́yìn ikú Àgbàkànmí, baba rẹ̀, tí wọ́n sì fi Aṣeere ẹni tí Àgbákànmí ti ń fìyà àìtọ́ jẹ  jẹ Baálẹ̀ dípò (Ògúndèjì 1992). Bákan náà ni ó jẹ́ pé ojú ọjà tí Obìnrin kan ti túfọ̀ ikú Adétutù nínú àhunpọ̀ ìtàn eré *Ẹfunẹtán Aníwúrà*: *Ìyálóde Ìbàdàn* ni ó mú kí ọjà tú, tí ìlú sì tipa bẹ́ẹ̀ dàrú.
- Ojúbọ inú igbórò òrìṣà odò Ẹ̀sìnmìnrìn ni Mọ́rèmí ti fa Olúorogbo fún Òrìṣà odò nínú *Mọrèmi* latọeọ̀ Dúró ladipọ. Igbórò kan ni a sì lè ka igbó àjẹ́ tí Gbọ̀n-ọ̀nkà ti lọ gba agbára nínú eré *Oba Kò So* sí. Bákan náà ni ó sì jẹ́ wí pé inú igbórò ní ojúbọ òrìṣà kan (Irúnmọlẹ̀ Ìpo-Òbìrí, ni wọ́n mú Ọba àti àwọn ìjòyè rẹ̀ lọ láti búra nínú *Ayé Yẹ Wọ́n tán* tí Akínwùmí Ìṣọ̀lá kọ.

### 4. 1. 4 Ìjẹyọ ajẹmẹ́dàá-ìtàn àti ìfìwàwẹ̀dá

- Ọ̀nà mìíràn pàtàkì tí fọ́nrán eré-oníṣe àbáláyé fi tún máa ń jẹ yọ nínú eré-oníṣe tòde òní ni nípasẹ̀ ṣíṣàmúlò ẹ̀dá ìtàn inú eré-oníṣe àbáláyé.

- Láti ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ẹ̀dá ìtàn nínú àwọn eré-oníṣe òde-òní ajẹ-mọ́dún-ìbílẹ̀, àwọn olùṣẹ̀dá eré níláti ṣàgbékalẹ̀ ìrísí, ìṣe àti ìwà ẹ̀dá ìtàn náà gẹ́gẹ́ bí wọ́n ṣe máa ń fi wọ́n hàn nínú àwọn ìṣeré ọdún ìbílẹ̀ àwọn. Èyí tí ó máa ń kọ́kọ́ hàn julọ ni ti àgbékalẹ̀ ìrísí. Èyí ni a óò tẹnu mọ jù lọ nínú ìjíròrò wa.
- Dúró Ládiípọ̀ ṣe èyí nígbà tí ó ṣàgbékalẹ̀ Ṣàngó nínú eré-oníṣe rẹ̀, *Ọba kò so*. Bákan náà ni ó ṣe láti ṣagbékalẹ̀ Mọ́rèmí, Ẹ̀sìnmìnrìn, àti àwọn jagunjagun oníko Ìgbò nínú eré-oníṣe *Mọrèmí*. Nípasẹ̀ ìmúra àwọn ẹlẹ́gùn Ṣàngó ni Dúró Ladipọ̀ ṣe ṣàgbékalẹ̀ Ṣàngó nínú eré rẹ̀. Ó ṣe àgbékalẹ̀ Mọ́rèmí bí olorì, ó sì ṣe ti òrìṣà odò Ẹ̀sìnmìrìn bí ìyálórìṣà. Àwọn eégún oníko ni ó fi ṣe àgbékalẹ̀ àwọn jagunjagun Ìgbò.  Kò sí àní àní pé látinú òye nípa àgbékalẹ̀ ajẹmọ́dún ìbílẹ̀ ni ó ti ṣe gbogbo àgbékalẹ̀ náà (Ògúndèjì, 1988)
- Ajílẹ́yẹ náà ṣe bí i ti Dúró ládipọ̀ nípa àgbékalẹ̀ Ṣàngó àti Ọya kalẹ̀ nínú eré-oníṣe rẹ̀ tí àkọ́lé rẹ̀ ń jẹ́ *Igbá Ṣàngó*. Bákan náà sì ni àgbékalẹ̀ Ògún nínú eré-onítàn àpilẹ̀kọ *Ògún Lákáàyé* tí Túbọ̀sún Ọládàpọ̀ kọ. Bí i ti Dúró Ladipọ̀ nípasẹ̀ òye ìmúra àwọn ẹlẹ́gùn Ṣàngó ni Ajílẹyẹ ṣe ṣèfìwàwẹ̀dá Ṣàngó inú eré rẹ̀. Nípasẹ̀ ìmúra ọdẹ tí ó tún ta mọ̀rìwò mọ́ra ni Túbọ̀sún Ọládàpọ̀ sì fi ṣe ìgbékalẹ̀ Ògún ní tirẹ̀.
- Bí a bá wo eré Ogunde tó pè ní *Yorùbá Ronú*, ọdún ìbílẹ̀ ni ìran tí wọ́n fi bẹ̀rẹ̀. Ogunde ṣe àgbékalẹ̀ ọba Fìwàjoyè bí àwọn ọba ilẹ̀ Yorùbá ṣe máa ń ṣe gẹ́lẹ́ lásìkò ọdún ìbílẹ̀, pàtàkì jùlọ nígbà tí wọ́n bá fẹ́ dá ifá ọdún. Bí ènìyàn kò tilẹ̀ fi ojú rí Fìwàjoyè tó jẹ́ ọba nínú eré náà, torí pé eré yìí jẹ́ eré inú fọ̀nrán oníkáséẹ̀tì, kedere ni ènìyàn yóó máa níran ìṣesí ẹ̀dá ìtàn náà láti ara ìsọ̀rọ̀ rẹ̀ àti èsì rẹ̀ nígbà tí baba ifá sọ fún un pé ọ̀tẹ̀ máà bẹ́ sílẹ̀ láàárín ìlú, tí ó sì fi kún ọ̀rọ̀ rẹ̀ náà pé ẹbọ nìkan ni wọ́n le fi tìkùn àjálù náà.

### 4.1.5 Ìjẹyọ ajẹmámùúlò èdè

- Kòṣe-é má-nìí ni ìṣàmúlò èdè fún àwọn eléré oníṣe pàápàá àwọn eléré oníṣe òde òní. Ọ̀nà ìṣàmúlò èdè tí àwọn eléré òde òní kúndùn àti-máa-lò ni ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì; èyí tí kò wọ́pọ̀ púpọ̀ nínú ìṣeré àbáláyé. Ìlò orin àti ìṣàré ni ó wọ́pọ̀ nínú ìṣeré àbáláyé. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ díẹ̀ nípa ìjẹyọ orin inú ìṣeré àbályé nínú àwọn eré òde òní’.

- Bí a bá wo eré-oníṣe *Mọrèmi* tí a ti fi ń ṣe àpẹẹrẹ láti òkè, ọ̀pọ̀lọpọ̀ orin tí *Dúró Ládiípọ̀* lò nínú eré yìí jẹ́ orin tí wọ́n ń kọ níbi ọdún Èdì ní Ifẹ̀. Àpẹẹrẹ kan ni èyí:

  Àjọkọ: Iná bàbá jorire
  Arìṣìkà, iná bàbá jó rire;
  Níjọ́ Ìgbò ṣẹ̀ké!
  Ẹnu Ìgbò mà kan o
  A rẹ́hìn ọ̀tá, a rẹ́hìn odì
  Morèmi Àjàṣorò, akin obìnrin
  Iná bàbá jorire
  Arìṣìkà, iná bàbá jó rire. (Ogúndèjì 1988: 130 – 131)

  Orin ọdún edì méjì ni Duro Ladipọ hun pọ̀ di orin kan ṣoso yìí ninú eré rẹ̀. Àkọ́kọ́ ni,

  Lílé: Iná bàbá jorire
  Gbígbè: Arìṣìkà,
  Lílé: Iná bàbá jó rire
  Gbígbè: Arìṣìkà. (Ògúndèjì 1988: 132 )

- Méjọ ni gbogbo ìlà orin inú eré-onítàn rẹ̀ bí a ti kọ ọ́ sókè yí. Láti inú orin ọdún edì ni ó ti mú àwọn ìlà mẹ́rin àkọ́kọ́ orin inú eré-onítàn rẹ̀; ìlà méjì àkọ́kọ́ jẹ́ orin ọdún edì kìn-ín-ní; ìlà méjì tí ó tẹ̀lé e sì wá látinú orin ọdún edì kejì. Àfikún ti ara rẹ̀ ni ìlà mẹ́rìn tí ó gbẹ̀yìn.
- Bákan náà ni nínú eré *Ọ̀ṣun* tí Dúró Ladipọ ṣẹ̀dá, orin tí wọ́n máa ń kọ ní àkókò ọdún Ọ̀ṣun Òṣogbo ni ó lò láti fi ṣe àgbékalẹ̀ òrìṣà Ọ̀ṣun. Ọ̀kan nínú àwọn orin náà ni:

  Lílé: Ẹ kóre yèyé o
  Gbígbè: Ẹ kóre yèyé Ọ̀ṣun
  Lílé: Ẹ kóre yèyé o
  Gbígbè: Ẹ kóre yèyé Ọ̀ṣun
  Lílé: Ọ̀ṣun kọ yẹ̀yẹ́ ò
  Gwbígbè: Ọ̀ṣun kọ yẹ̀yẹ́ yín
  Lílé: Ọ̀ṣun kọ yẹ̀yẹ́ ò
  Gbígbè: Ọ̀ṣun kọ yẹ̀yẹ́ yín
  Lílé: Ọlọ́mọ nìyá ò
  Gbígbè: Ọlọ́mọ nìyá àwa

- Nínú eré-onítàn àpilẹ̀ẹ̀kọ *Ẹfúnróye Tinubu*, Akínwùmí Ìṣọ̀lá náà ṣe àmúlò ijó ọdún Ẹ̀yọ̀ láti fi kádìí àgbékalẹ̀ ayẹyẹ ọdún kẹta tí Ọba Dòsùnmú gorí oyè nínú apá kìn-ín-ní, ìran kìn-ín-ní (1 – 2)

- Bákan náà ni a rí ìjẹyọ ọdún Ifá ní tòtò ìparí iran kìn-ín-ní eré náà níbi tí wọ́n ti kọ orín ifá, tí wọ́n sì ti sun ìyẹ̀rẹ̀.
- Ó yẹ kí a tọ́ka sí i pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn olùṣẹ̀dá eré-onítàn òde òní ní í máa ṣàmúlò àwọn èròjà lítíréṣọ̀ alohùn tí í máa jẹyọ nínú ọdún ìbílẹ̀ bí a ti fi hàn yìí bí wọ́n kò tilẹ̀ ṣe àgbékalẹ̀ ọdún ìbílẹ̀. Àpẹẹrẹ irú àmúlò bẹ́ẹ̀ ni ọfọ̀ pípè tí ó súyọ nínú ìwé eré-onítàn *Ẹfúnṣetán Aníwúrà*, láàrin Látòósà àti Ẹfúnṣetán pẹ̀lú àmúlò rárà tó jẹ yọ nínú eré-onítàn àpilẹ̀kọ *Àárẹ Àgò Aríkúyẹrí* nígbà tí Ògunrìndé Ajé ń bọ orí rẹ̀.

5. 0 Ìsọníṣókí

- A kò le ṣàì tún tẹnu mọ́ ọn pé eré-oníṣe òde òní kò le wà láì ṣe àmúlò àwọn àbùdá eré-oníṣe àbáláyé. Ohun tí ó fa èyí ni pé àwùjọ tí ó bí eré-oníṣe àbáláyé náà ló gba eré-oníṣe òde òní ní àlejò. Kí àwọn olùṣẹ̀dá eré-oníṣe òde òní tó lè tẹ́ àwọn òǹwòran wọn, tí wọ́n jẹ́ ojúlówó ọmọ Yorùbá lọ́rùn dáradára, wọ́n gbọ́dọ̀ máa ṣe àmúlò àwọn èròjà tí ó jẹ mọ́ ìrírí àbínibí wọn, tí ó rọ̀ mọ́ àṣà, ẹ̀sìn, èrò àti ìṣe wọn.
- Láti tán ìfẹ́ àwùjọ lọ́rùn ló mú àwọn eléré oníṣe òde òní máa ṣe àmúlò àwọn àbùdá eré-oníṣe àbáláyé. Èyí sì ni ó fà ìjẹyọ eré-oníṣe àbáláyé nínú ti òde òní. Kódà a lè sọ pé eré-oníṣe àbáláyé (pẹ̀lú àwọn lítíréṣọ̀ àlohùn àbáláyé yòókù) ni eré-oníṣe òde òní fi ṣe ìtìsẹ̀; tàbáláyé ni orísun ìjéré oníṣe Yorùbá ti òde òní. Lọ́rọ̀ kan láì sí àwọn èròjà àbáláyé nínú eré-oníṣe òde òní a kò ní í lè fọwọ́ sọ̀yà pé eré-oníṣe Yorùbá ni wọ́n.
- Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti jíròrò lórí bí eré-oníṣe àbáláyé ṣe máa ń jẹ yọ nínú eré-oníṣe òde òní. Ọ̀nà márùn-ún ni ìjíròrò wa náà pín sí: ìjẹyọ nípa àhùnpọ̀ ìtàn, ìjẹyọ nípa kókó ọ̀rọ̀, ìjẹyọ nípa ibi ìṣeré/ibùdó ìtàn, ìjẹyọ nípa ẹ̀dá ìtàn àti ìfìwàwẹ̀dá àti ìjẹyọ nípa ìmúlò èdè.
- A tọ́ka sí ohun tí ó ṣokùnfà ìjẹyọ àwọn àbùdá/ fọ́n-anrán/ ọmọlẹ̀ eré-oníṣe àbáláyé nínú tòde òní. A wí pé àwọn eléré/ òǹkọ̀wé eré-oníṣe òde òní jẹ́ ọmọ àwùjọ Yorùbá tí wọ́n ṣàgbékalẹ̀ eré wọn fún ìgbádùn àwọn ọmọ àwùjọ Yorùbá. Láti mú kí akitiyan wọn jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà ni wọ́n fi níláti máa lo àwọn èròjà eré-oníṣe àbáláyé.

6. 0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ní ṣókí, ṣe àlàyé ohun tí ó ń ṣe òkùnfà ìjẹyọ eré-oníṣe àbáláyé nínú eré-oníṣe òde òní.
2. Àwọn àbùdá eré-oníṣe àbáláyé Yorùbá wo ni ó máa ń jẹ yọ nínú eréoníṣe òde òní?
3. Dárúkọ eré òníṣe òde òní mẹ́erin nínú èyí tí ìtàn ìwáṣẹ̀ ọdún ìbílẹ̀ ti jẹyọ.
4. Ọ̀nà wo ni ìlò èdè ré oníṣe ọdún ìbílẹ̀ máa ń sábàá gbà jẹyọ nínú àwọn eré-onítàn òde òní? Fi àpẹẹrẹ gbe ìdáhùn rẹ lẹ́sẹ̀.

7. 0 Ìwé ìtọ́kasí


Fálétí, A. 1970. *Baṣọrun Gáà*, Oníbọnòjé Press and Book Indusries Nig. Ltd. Ibàdàn.

Ìṣọ̀lá, A. 1972. *Ẹfúnṣetán Aníwúrà: Ìyálóde Ìbàdàn*. Oxford University Press Ltd.Ibadan,

Ìṣọ̀lá, A. 2009. *Ẹfúnróye Tinúubú*. D. B. Martoy Books, Ìbàdàn.

Ìṣọ̀lá, A. 2009. *Ayé Yẹ Wọ́n Tan*. D. B. Martoy Books, Ìbàdàn.

Ogundeji, P. A. 1988. 'A Semiotic Study of Dúró Ladipọ's Mythico- Historical Plays' , Ph.D Thesis, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Ogundeji, P. A. 1992. *Yorùbá Drama I*. Ìbàdàn External Studies Programme, now Distance Learning Centre, University of Ibadan, Ibadan.

Ogundeji, P. A. 1992. *Introduction to Yorùbá Written Literature*. Ìbàdàn External Studies Programme, now Distance Learning Centre, University of Ibadan, Ibadan.

Ogundeji, P. A. 2006 '*Ojú Ọjà:* A Socio-commercial Depiction of the Market Place in Yorùbá Drama', *Yorùbá: Jọ́nà Ẹgbẹ́ Onímọ̀ Yorùbá ti Orílẹ̀ Èdè Nàìjíría* Vol. 3, No 2: 1 – 14

Ogundeji, P. A. 2000. *Ritual as Theatre, Theatre as Ritual: The Nigerian Example*. Ìbàdàn Cultural Studies Group, Ìbàdàn.

Ogundeji, P. A. 2001. '*Eré-oníṣe* Yorùbá' nínú Ẹ̀kọ́ *Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá-èdè, Lítíréṣọ̀ àti Àṣà,* Bádé Àjàyí (olóòtú) Ẹ́ka Ẹ̀kọ́ Ìmọ̀ Ẹ̀dá Èdè àti àwọn Èdè ilẹ̀ Nàìjíríà, Yunifasiti Ìlọrin, Ìlọrin o. i. 167-188.

Ògúnníran, L. 1977 *Ààrẹ Àgò Aríkúyẹrí* Macmillan Publishers Nigerian Ltd. Lagos.

Ọdúnjọ, J. F. *Agbàlọ́wọ́mérìí:Baálẹ̀ Jòǹtolo*, Longman Nigerian Ltd., Lagos.

Ọladàpọ̀, Ọlátúbọ̀sún 1983 *Ògún Lákáayé,* Oníbọnòjé Press and Book Indusries Nig. Ltd. Ibàdàn.